# ÈYÍ GAN-AN NI ẸSÌN ÌSLĀM

Ìwòye tó múnádóko nípa ẹ̀sìn tó ń yára dàgbàsókè jùlọ ní gbogbo àgbáyé





**Àwòràn àwọn Mùsùlùmí, èyí tí a yà láti ojú òfurufú nígbà tí wọ́n da ojú kọ *Ka‘bah,* èyí tí Ọlọ́hun pa Ànábì Rẹ̀ Ibāhīm láṣẹ pé kí ó kọ́ ọ, tí Ó sì pa àwọn Mùsùlùmí  láṣẹ pé kí wọ́n máa da ojú kọ́ ọ nígbà tí wọ́n bá ń kírun ní ibikíbi tí wọ́n bá wà**

THIS IS ISLAM

# ÈYÍ GAN-AN NI ẸSÌN ÌSLĀM

**Ìwòye tó múnádóko nípa ẹsìn tó ń yára dàgbàsókè jùlọ ní gbogbo àgbáyé**

**FAHD BN SĀLIM BĀHIMĀM**


**Àtẹ̀jáde àkọ́kọ́**
2021

**Gbogbo ẹ̀tọ́ títẹ ìwé yìí jade jẹ́ ti iléiṣẹ́ ìtọ́ka ìgbàlódé nìkan**



- Ṣé kò pàtàkì sí ọ, kí o rí, ní ọ̀nà tí ó fi ojú hàn jùlọ, nípa ẹ̀sìn tí iyàn pọ̀ nípa rẹ̀ jùlọ nínú àwọn ilé àti ìwé ìròyìn tí ó wà ní àyíká rẹ̀?..
- Ṣé kò ha tọ́ kí o kóraró fún ìṣẹ́jú kan, nítorí kí o le ní àmọ̀jinlẹ̀, nípa ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀sìn tí ó tàn ká jùlọ ní gbogbo àgbáyé, tí àwọn ènìyàn sì ń wọnú rẹ̀ jùlọ, ní ìbámu sí àwọn kíka òǹkà ìṣẹ̀lẹ̀ àgbáyé?..
- Ṣé kò dùn mọ́ ọ kí o wádìí nípa ọ̀làjú àwọn ènìyàn miíràn àti ìròrí wọn nípa ìṣẹ̀mí-ayé, ẹ̀sìn àti gbogbo àgbáyé tó yí wa ká?..
- Kílódè tí o kò ní fún ara rẹ ní àǹfààní láti rí àwọn ẹ̀kọ́ tí a fi ẹ̀rí, láti àwọn ìpìlẹ̀ rẹ̀, gbè lẹ́sẹ̀ nípa ẹ̀sìn Islām … lẹ́yìn náà tí wà á sì gbé ìdájọ́ lé e lórí pẹ̀lú ọ̀rọ̀ rẹ̀ àti làákàyè rẹ̀?..

Tí o bá rí èyí, tàbí nǹkankan nínú rẹ̀, sí ohun tí ó pàtàkì, tàbí ó jẹ́ ohun tí ò ń jẹ̀rán rẹ̀, a jẹ́ wí pé dájúdájú ìwé yìí yóò jẹ́ ìrànlọ́wọ́ fún ọ láti jẹ́ kí o rí ohun tí ò ń wá..



Níbo ni *Al-Qur’ān* ti wá? 84

Ìbéèrè tó mú ọgbọ́n lọ́wọ́, èyí tó máa ń yára jẹyọ nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìwé mímọ́ àwọn Mùsùlùmí: *Al-Qur’ān*, àti Ànábì Muḥammad – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a –. Kílódé tí ó jẹ́ dandan fún wa láti gba ẹ̀gbàwá àwọn Mùsùlùmí nípa ìtàn yìí? Ṣé kò tọ́ fún wa kí á mú àwọn ìbéèrè wá lórí rẹ̀?

# Àwọn àkòrí ìwé yìí

Àwọn ìbéèrè tó jẹ gbogbo wa lógún.. 12

- Ẹ̀sìn *Islām*
- Ìtumọ̀ gbólóhùn *Islām*
- Ẹ̀sìn *Islām* ni ẹ̀sìn gbogbo àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun

Jíjẹ́ ẹ̀sìn àgbáyé ẹ̀sìn *Islām* 16

- Níní àkàkún àwùjọ, ìpín kan nínú ìgbàgbọ́ òdodo ni
- Ẹ̀sìn ìmọ̀
- Ẹ̀sìn *Islām* kó gbogbo agbegbe ìgbésí-ayé ènìyàn sínú
- Ẹ̀sìn ìbára ẹni ṣe àti ṣíṣe àṣepọ̀

Àdẹ́dàá kan ṣoṣo.. Ẹni tí à ń jọ́sìn fún kan ṣoṣo 32

- Àjọṣepọ̀ tó wà láàrin òfin àdámọ̀ àti òfin ìdájọ́ ẹ̀sìn Ọlọ́hun
- Kò sí jíjẹ́ alagbà nínú ẹ̀sìn *Islām*
- Ṣé ìlànà àrà ọ̀tọ̀ kan ń bẹ fún wíwọnú ẹ̀sìn *Islām* bí?

Àwọn wo gan-an ni Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun òtítọ́? 40

- Jíjẹ́ abara Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun
- Wọ̀ntún-wọ̀nsì nípa ipò Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun
- Ipò ẹ̀sìn *Islām* nípa àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun

Ipò ẹ̀sìn *Islām* nípa Ànábì ‘Īsā – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – 44

Tani Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn *Islām* rán 50

- Ìrin-àjò kíákía láti mọ̀ nípa Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn *Islām* rán, Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –

Muḥammad, jẹ́ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, nínú ìwòye àwọn onídéédé 56

Díẹ̀ nínú ìtàn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, Muḥammad, àti àwọn ìwà rẹ̀ — 62

- Ìtẹríba
- Àánú
- Ṣíṣe déédé
- Ṣíṣe dáadáa àti lílawọ́
- Sùúrù àti àfaradà Rẹ̀
- Rírí ayé sá
- Pípé àdéhùn

Díẹ̀ nínú àwọn ọ̀rọ̀ Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – — 72

*Al-Qur'ān* alápọ̀n-ọ́nlé jẹ́ iṣẹ́-ìyanu gbére fún ẹ̀sìn *Islām* — 78

- Ìṣẹ́ ìyanu tí ń bẹ̀ níbi ṣíṣọ́ ọ
- Ìkánilagara ti àlàyé àti ẹ̀mí

Níbo ni *Al-Qur'ān* ti wá? — 84


- Àwọn fífi ẹ̀sùn kanni léraléra
- Kílódé tí a kò kà á sí jíjẹ́ akin lásán
- Bóyá àwọn ìwé tó tún àgbékalẹ̀ wọn rọ ni
- Pàápàá ìtàn-ayé tó ń ṣe ìyàtọ̀
- Kálukú ni ó ní gbólóhùn tí yóò sọ gbẹ̀yìn
- *Sūratul-Fātiḥah*

Àwọn ìjọsìn nínú ẹ̀sìn *Islām*, kín ni pàápàá wọn? — 94

- Àwọn orígun ìrun
- Kín ni ó fa lílà iwọ̀ bọ wa lọ́rùn àti dídán wa wò?
- Ìrun kíkí
- *Zakāh* yíyọ
- Ààwẹ̀ gbígbà
- *Ḥajj* ṣíṣe

Ẹbí Nínú ẹ̀sìn *Islām* — 110

- Ẹ̀sìn *Islām* kanpá mọ́ ìpìlẹ̀ gbígbé ìyàwó àti kíkó ẹbí jọ
- Ẹ̀sìn *Islām* fún ẹnikọ̀ọ̀kan nínú ẹbí ní àpọ́nlé tí ó pé, bóyá ó jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin
- Ẹ̀sìn *Islām* ṣe ojú kòkòrò lórí fífi ìpìlẹ̀ bíbu ọ̀wọ̀ àti ṣíṣe àpọ́nlé fún àwọn bàbá àti àwọn ìyá wa lélẹ̀, àti jíjígìrì sí ṣíṣe àmójútó wọn, àti títẹ̀lé àṣẹ wọn títí di ọjọ́ ikú
- Ẹ̀sìn *Islām* pàṣẹ ṣíṣọ́ iwọ̀ àwọn ọmọkùnrin àti àwọn ọmọbìnrin àti jíjẹ́ ọ̀ranyàn ṣíṣe déédé láàrin wọn
- Ọlọ́hun ṣe dída ẹbí pọ̀ ní ọ̀ranyàn lórí Mùsùlùmí



## Ẹbí Nínú ẹ̀sìn *Islām* 110

Òdodo ni ọ̀rọ̀ yìí jẹ́ nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹbí, ní àsìkò tí a wà yìí pé; ó jẹ́ àkójọpọ̀ àwọn ènìyàn kọ̀ọ̀kan, tí àwọn kọ̀kọ́rọ̀ ọlọ́kan-ò-jọ̀kan wà lọ́wọ́ wọn fún ilé kan ṣoṣo!



# Bíbá ara rẹ́ ẹ̀sìn àti làákàyè

136

Apákan nínú àwọn ènìyàn máa ń lérò pé dájúdájú ẹ̀sìn tako làákàyè, ó sì tako ìlànà ìmọ̀; nítorí pé dájúdájú ẹ̀sìn jẹ́ orísun àwọn èròkerò, àwọn àdáparọ̀ àti ìròrí asán.


Ipò obìnrin nínú ẹ̀sìn *Islām* —— 116

- Díẹ̀ nínú àwọn ìdájọ́, èyí tó so mọ́ bíbọ̀wọ̀ fún obìnrin ni ohun tó ń bọ̀ yìí
- Àwọn obìnrin tí ẹ̀sìn *Islām* kanpá mọ́ pípàtàkì wọn
- Kò sí ààyè fún ìjà láàrin ìran méjèèjì nínú ẹ̀sìn *Islām*
- Àjọṣepọ̀ láàrin ọkùnrin àti obìnrin
- Irú àjọṣepọ̀ tó wà láàrin ọkùnrin àti obìnrin nínú ẹ̀sìn *Islām*
- Kílódé tí ẹ̀sìn *Islām* ṣe wíwọ *ḥijāb* níwájú àwọn ọkùnrin àjòjì ní òfin?
- Àwọn òǹdè tó wà fún àjọṣepọ̀ láàrin ọkùnrin àti obìnrin àjòjì

Òfin ẹ̀sìn *Islām* nípa oúnjẹ jíjẹ àti nǹkan mímu —— 126

- Ẹlẹ́dẹ̀
- Àwọn ọtí àti àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn
- Báwo ni *Al-Qur'ān* ti bá mímu àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn àti ọtí lò?

Ẹ̀ṣẹ̀ àti ìrònúpìwàdà —— 132

Bíbá ara rẹ́ ẹ̀sìn àti làákàyè —— 136

- Àwọn ohun tó máa ń kó ààyè bá rírorí ní ọ̀nà tó ní àláàfià gẹ́gẹ́ bí *Al-Qur'ān* ti ṣàlàyé rẹ̀

Ẹ̀sìn àláàfià ni ẹ̀sìn *Islām* —— 142

- Ẹ̀sìn *Islām* ni ẹ̀sìn tó ń yára tàn ká jùlọ ní ayé òde-òní
- Ṣé ó je àwọn ènìyàn nípa láti wọnú ẹ̀sìn *Islām* bí?

Àfiwé Láàrin ẹ̀sìn *Islām* àti ìṣesí apákan nínú àwọn Mùsùlùmí —— 148

- Ààyè titun



# Àwọn ìbéèrè tó jẹ gbogbo wa lógún..

Tani nínú wa ni kò ti kóra ró fún ìṣẹjú kan rí nínú ìṣẹ̀mí-ayé rẹ̀, láti bi ara rẹ̀ léèrè... pé: Kín ni ń ṣẹlẹ̀? Tani mi? Láti ibo ni mo ti wá? Ibo ni mo ń lọ? Ibo ni ibùṣẹ̀rísí mi? Kín ni èròngbà tí ń bẹ ní abẹ́ gbogbo ohun tí ń bẹ ní ayé yìí? Kín ni láríjà gbogbo wàhálà àṣekúdórógbó yìí, nínú ayé, tí ó bá jẹ́ wí pé òpin gbogbo rẹ̀ ni ikú, dídi ìyẹ̀pẹ̀ àti ṣíṣe àìsí?

Àwọn Mùsùlùmí àti gbogbo àwọn ẹlẹ́sìn tí ó wá láti sánmà gbàgbọ́ pé; dájúdájú ìṣẹ̀mí ènìyàn, láìsí ìgbàgbọ́ òdodo pẹ̀lú bíbẹ Ọba Adẹ́dàá, tí Ó jẹ́ Onídééde àti pẹ̀lú bíbẹ ìṣẹ̀mí mìíràn, tí ẹni tí ó ṣe dáadáa yóò rí ẹ̀san rẹ̀ níbẹ̀, tí ẹni tí ó ṣe aburú náà yóò sì rí ìyà ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ níbẹ̀, jẹ́ ere panrangandan, tí kò ní ìtumọ̀, ó tún jẹ́ ìyà àti ìniran tí kò ní ààrọ̀, àti ìfẹ̀míwéwu tí kò ní èrè kankan nínú, tí kò sì ní iye kankan lórí.

Àti pé dájúdájú kò rọrùn kí á gbọ́ àgbọ́yé títako ara wọn ìṣẹ̀mí-ayé àti ọgbọ́n tí ń bẹ níbi ìlekoko ìṣẹ̀mí-ayé, àti àṣìṣe àti ṣíṣe déédé àti ìnira àyàfi nígbà tí a bá gbàgbọ́ lódodo pẹ̀lú Ọlọ́hun Ọba, Adẹ́dàá, Olùdarí, Ọlọ́gbọ́n, Onídééde, tí Ó ṣe òpin fún ìṣẹ̀mí-ayé yìí, èyí tí gbogbo ènìyàn yóò rí ìpín rẹ̀, lẹ́yìn rẹ̀, ní ìbámu sí ohun tí ó tì síwájú àti ohun tí ó ṣe nísẹ̀..

Nígbà náà nìkan sọ́ ni ìgbàgbọ́ tó jinlẹ̀, pẹ̀lú gbogbo ìhùwàsí wa àti àwọn àgbọ́yé wa, èyí tí à ń pèpè sí – bíi déédé, ìfẹ́, níní àánú ara ẹni, òdodo síso, sùúrù àti mímáa kẹ́ ara ẹni – yóò di pàápàá tí ẹ̀mí ènìyàn tí bá rẹ̀.. tí ìpènìjà yóò ní ìtumọ̀ rẹ̀, tí àṣeyọrí yóò ní ìtọ́wò rẹ̀, tí sùúrù yóò sì ní adùn rẹ̀.

A ó ríi pé *Al-Qur'ān* alápọ̀n-ọ́nlé, èyí tí í ṣe ìwé mímọ́ àwọn Mùsùlùmí, ń tọ́ka sí èyí. Dájúdájú Ọlọ́hun sọ fún wa, nínú rẹ̀, nípa àwọn onílàákàyè àti àròjinlẹ̀, Ó sọ wí pé: **{Wọ́n tún máa ń ronú nípa dídá sánmà àti ilẹ̀, (wọn yóò máa wí pé:) Ìrẹ Ọlọ́hun Ọba wa! O kò dá èyí lásán, mímọ́ ni fún Ọ}** (*'Āl-'Imrān*: 191).

## Ẹ̀sìn *Islām*:

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ẹ̀sìn tí ń bẹ lórí ilẹ̀, wọ́n sọ wọ́n ní orúkọ ní àfitì sí ènìyàn kan tàbí ìjọ kan tàbí àwọn ìlú tí ẹ̀sìn náà ti hàn síta. Ẹ̀sìn *Masīḥiyyah*, ní àpẹ̀júwe, wọ́n yọ orúkọ rẹ̀ látara orúkọ asiwájú wa *Al-Masīḥ* – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a –, ẹ̀sìn *Yahūdiyyah*, wọ́n ṣe àfitì rẹ̀ sí ìdílé *Yahūdhā*, ẹ̀sìn Bùdà, wọ́n ṣe àfitì rẹ̀ sí *Būdhā* tí ó dá a sílẹ̀, ẹ̀sìn *Hindūsiyyah*, wọ́n ṣe àfitì rẹ̀ sí ìlú Índíà, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ...

Ṣùgbọ́n ẹ̀sìn *Islām*, dájúdájú kò fi ara rẹ̀ tì sí ènìyàn kan pàtó, kò fi ara rẹ̀ tì sí ìdílé kankan tàbí ìran kankan tàbí ìjọ kankan. Èyí rí bẹ́ẹ̀, nítorí pé dájúdájú kò ṣẹ̀ṣà pẹ̀lú ìjọ kankan nínú abara ènìyàn débi wí pé a ó ṣe àfitì rẹ̀ sí i. Kì í sì ṣe ènìyàn kan ni í ó dá a sílẹ̀ débi wí pé a ó ṣe àfitì rẹ̀ sí i. Ògédé orúkọ tí wọ́n sọ ọ́ ni ẹ̀sìn *Islām*.

## Ìtumọ̀ gbólóhùn *Islām*:

Nígbà tí a bá ṣẹ́rí padà sí ìpìlẹ̀ gbólóhùn *Islām* nínú èdè Lárúbáwá, dájúdájú ó kó ọlọ́kan-ò-jọ̀kan àwọn ìtumọ̀ tí ó dá lórí gbígbàfà fún Ọlọ́hun, títẹ́ríbà, títẹ̀lé àṣẹ Ọlọ́hun, ṣíṣe àfọ̀mọ́ ìjọsìn fún Ọlọ́hun, ìfọkànbalẹ̀ àti ìfàyàbalẹ̀ sínú.

Ẹ̀sìn *Islām*: Ohun ni gbígbàfà àti títẹ́ríba tí ó pé fún Ọlọ́hun Ọba, Adẹ́dàá, Olùkápá, àti ṣíṣọ́ra níbi gbogbo àwọn ìran ṣíṣe ìjọsìn fún ẹlòmíràn yàtọ̀ sí I.

Eléyìí ni ìtumọ̀, èyí tí kíkanpá mọ́ ọn wá nínú ọlọ́kan-ò-jọ̀kan àwọn āyah *Al-Qur'ān*.

*Al-Qur'ān* fún wa ní ìró pé: Dájúdájú ẹni tí ó bá da ojú kọ Ọlọ́hun pẹ̀lú ọkàn rẹ̀ àti gbogbo oríkèé ara rẹ̀, tí ó tẹ́ríba, tí ó gbàfà, tí ó mú àwọn ohun tí Ọlọ́hun paṣẹ rẹ̀ ṣẹ, tí ó sì jìnnà sí àwọn ohun tí Ó kọ̀ nípa rẹ̀, dájúdájú ó ti dìrọ̀ mọ́ okùn ọlà, èyí tí kò le já, ó sì ti jèrè gbogbo oore. **"Àti pé ẹnikẹ́ni tí ó bá gbàfà ojú rẹ̀ sí ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun, tí ó sì jẹ olùṣedáadáa, nígbà náà dájúdájú o ti gbá okùn tí ó nípọn mú, àti pé dájúdájú ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun ni àtubọ̀tán àwọn ọ̀ràn yóò padà sí"** (*Luqmān*: 22).

Nígbà náà, a jẹ́ wí pé ẹ̀sìn *Islām* ni ìjẹ́-ẹrúsìn tí ó pé fún Ọlọ́hun, àti òmìnira kúrò níbi títẹ́ríba àti jíjẹ́-ẹrúsìn fún ẹlòmíràn yàtọ̀ sí I. Àti pé Mùsùlùmí ni ènìyàn tí ó ṣe àfọ̀mọ́ ọkàn rẹ̀ fún Ọlọ́hun níbi ìjọsìn rẹ̀, àti ẹni tí àláàfíà ń ṣẹ̀mí nínú ara rẹ̀, tí ó sì ń fọ́n àláàfíà ká láàrin àwọn tí ń bẹ ní àyíká rẹ̀.

**Ṣùgbọ́n, ṣé èyí ni ohun tí gbogbo àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun mú wá bí?**

## Ẹ̀sìn *Islām* ni ẹ̀sìn gbogbo àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun:


*Al-Qur'ān* tún fi rinlẹ̀ pé dájúdájú gbogbo ìjọ ayé, láti ìgbà dégbà, ni Ọlọ́hun, níti pàápàá, gbé Ìránṣẹ́ dìde sí, èyí tí yóò máa kọ́ wọn ní ẹ̀sìn Ọlọ́hun. Ọ̀rọ̀ tún wá, nínú *Al-Qur'ān*, fún Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – pé: **{Dájúdájú Àwa ni A rán ọ ni olùfúnni ní ìró ìdùnnú àti olùkìlọ̀, àti pé kò sí ìjọ kankan àyàfi kí olùkìlọ̀ ti rékọjá nínú rẹ̀}** (*Fāṭir*: 24). Nítorí náà gbogbo àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun wá pẹ̀lú ẹ̀sìn òdodo, wọn kò sì yapa ara wọn níbi ohun tí wọ́n fi rán wọn níbi ìgbàgbọ́ àti ìpìlẹ̀ àwọn ìdájọ́ àti ìwà.

Ẹ̀sìn *Islām*, èyí tí òpin àwọn Ànábì, Muḥammad – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a – dé pẹ̀lú rẹ̀, síwájú ohun tó lé ní ẹgbẹ̀rún àti ọgọ́rùn-ún mẹ́rin ọdún, jẹ́ ìtẹ̀síwájú fún ẹ̀sìn tí gbogbo àwọn Ànábí Ọlọ́hun pátápátá mú wá. *Al-Qur'ān* sì pa àwọn Mùsùlùmí láṣẹ pé kí wọ́n gbàgbọ́ pẹ̀lú ohun tí àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun tó ti síwájú gbàgbọ́, bíi Ibrāhīm, Isḥāq, Ya'qūb, Mūsā àti 'Īsā. **"Sọ wí pé: A gba Ọlọ́hun gbọ́, àti ohun tí wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún wa, àti ohun tí wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún Ibrāhīm, Ismā'īl, Isḥāq àti Ya'qūb, àti ohun tí wọ́n fún Mūsā àti 'Īsā, àti ohun wọ́n fún àwọn Ànábì láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun Ọba wọn. A kò ní ṣe ìyàtọ̀ láàrin ẹnìkankan nínú wọn, àti pé Òun ni àwa jẹ́ olùgbàfà fún"** (*Al-Baqarah*: 132)

Nínú ohun tí ó yẹ kí á bojú wò ni pé, dájúdájú *Al-Qur'ān* fún wa ní ìró nípa àsọtẹ́lẹ̀ Ànábì Ibrāhīm; baba àwọn Ànábì, fún àwọn ọmọ rẹ̀, bẹ́ẹ̀ náà ni Ànábì Ya'qūb fún àwọn ọmọ rẹ̀, nígbà tí ẹ̀mì rẹ̀ fẹ́ bọ́, pẹ̀lú ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé: Dájúdájú Ọlọ́hun ti ṣẹ̀ṣà ẹ̀sìn òdodo fun yín, nítorí náà ẹ dúró sinsin lóri ẹ̀sìn *Islām* títí tí ikù yóò fi dé wá ba yín. **"Ibrāhīm sì sọ àsọtẹ́lẹ̀ rẹ̀ (ìgbàfà fún Ọlọ́hun) fún àwọn ọmọ rẹ̀ àti Ya'qūb pẹ̀lú (sọ àsọtẹ́lẹ̀ bẹ́ẹ̀) pé ẹyin ọmọ mi! Dájúdájú Ọlọ́hun ti ṣẹ̀ṣà ẹ̀sìn (òdodo) fun yín, nítorí náà ẹ má ṣe kú àyàfi kí ẹ jẹ́ olùgbàfà lódodo"** (*Al-Baqarah*: 132).

Ẹ̀sìn *Islām* jẹ́ ìtẹ̀síwájú fún ẹ̀sìn gbogbo àwọn Ànábí Ọlọ́hun pátápátá. Ọkan ṣoṣo ni àdìsọ́kàn, pàápàá ìpìlẹ̀ rẹ̀ kò le yípada. Ìyípadà máa ń wà níbi òfin ẹ̀sìn àti ìfọ́síwẹ́wẹ́ àwọn ìdájọ́ ní ìbámu sí ohun tí ó bá ìṣesí àwọn àsìkò ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ mu, títí tí Ọlọ́hun fi gbé Ìránṣẹ́ ìgbẹ̀yìn; Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – dìde, kí ó le fi òfin ẹ̀sìn ìgbẹ̀yìn rinlẹ̀ fún gbogbo ènìyàn pátápátá.

Ìdí nìyí, tí *Al-Qur'ān* fi fi rinlẹ̀, pẹ̀lú àlàyé tó fojú hàn kedere pé dájúdájú ọ̀kan ṣoṣo ni ẹ̀sìn, òun náà si ni ẹ̀sìn *Islām*, àti pé dájúdájú ìyapa-ẹnu, èyí tí à ń rí láàrin àwọn tó ń ṣe àwọn ẹ̀sìn tó sọ̀kalẹ̀ láti sánmà, níbi àwọn abala àdìsọ́kàn kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe àwọn àyípadà, èyí tó gbé wọn jìnnà sí ohun tí àwọn Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun rán sí wọn mú wá. **"Dájúdájú ẹ̀sìn, ní ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun ni ẹ̀sìn *Islām*. Àti pé àwọn ẹni tí a fún ní Tírà kò yapa ẹnu àyàfi lẹ́yìn ìgbà tí ìmọ̀ ti dé wá bá wọn, níti ìkọjá ààlà láàrin ara wọn, àti pé ẹnikẹ́ni tó bá ṣe àìgbàgbọ́ pẹ̀lú àwọn àmí Ọlọ́hun, dájúdájú Ọlọ́hun nígbà náà jẹ́ Olùyára ṣe ìṣirò ìṣẹ́"** (*'Āl-'Imrān*: 19).



# Jíjẹ́ ẹ̀sìn àgbáyé ẹ̀sìn *Islām*

Nínú ohun tó ya ènìyàn lẹ́nu ni pé dájúdájú, gbólóhùn (ìran Lárúbáwá) kò wá nínú *Al-Qur'ān*, pẹ̀lú pé èdè wọn ni ó fi sọ̀kalẹ̀, tí ó sì jẹ́ wí pé ààrin wọn ni wọ́n ti gbé Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, Muḥammad dìde. A ó ríi ní ayé òde-òní pé àwọn ìran Lárúbáwá jẹ́ àwùjọ kékeré láàrin àwọn Mùsùlùmí. Kódà wọn kò ju 20% lọ nínú òǹkà àwọn Mùsùlùmí. Orílẹ̀-èdè Mùsùlùmí tó tóbi jùlọ ni *Indonesia*, èyí tó wà ní jìnnà jìnnà Gúúsù-ìlàòrùn Ásíà. Kódà àwùjọ àwọn Mùsùlùmí kékeré ní orílẹ̀-èdè India nìkan ṣoṣo fẹ́ẹ̀ tó òǹkà ìlọ́po méjì orílẹ̀-èdè Lárúbáwá tó tóbi jùlọ.


Ẹ̀sìn *Islām* dé ní ìkẹ́ àti ìmọ̀nà fún gbogbo ìran pẹ̀lú bí ọ̀làjú wọn, ìpìlẹ̀ wọn, àṣà wọn àti ìlú wọn ti yàtọ̀ sí ara wọn, gẹ́gẹ́ bí ó ti wá nínú *Al-Qur'ān* pé: **"A kò rán ọ bíkòṣe láti jẹ́ ìkẹ́ fún gbogbo àgbáyé"** (*Al-'Anbiyā': 107*).

Ẹ̀sìn *Islām* ṣe àgbékalẹ̀ ìwòye fún jíjẹ́ oníran-ǹran àwọn ènìyàn, ní ọ̀nà tí ètò ìṣẹ̀mí-ayé mìíràn kò mọ̀, tí àwọn ìran ènìyàn tí ó wà lórí ilẹ̀ kò sì bá a sáábà.

Jẹ́ kí á ronú sí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ *Al-Qur'ān* yìí, èyí tí kò bá ìran Lárúbáwá nìkan wí, tí kò sì bá àwọn Mùsùlùmí nìkan wí, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ọ̀rọ̀ tí wọ́n da ojú rẹ̀ kọ gbogbo ìran ènìyàn lápapọ̀ pẹ̀lú gbogbo ìpìlẹ̀ wọn àti ìlànà ìròrí wọn. Ọlọ́hun, nínú *Al-Qur'ān*, sọ wí pé: **"Ẹ̀yin ènìyàn! Dájúdájú Àwa ni A ṣẹ̀dá yín látara ọkùnrin kan àti obìnrin kan, A sì ṣe yín ní àwọn ẹ̀yà àti àwọn ìran, kí ẹ le dá ara yín mọ̀. Dájúdájú ẹni tí ó ni àpọ́nlé jùlọ lọ́dọ̀ Ọlọ́hun nínú yín ni olùbẹ̀rù Ọlọ́hun jùlọ nínú yín"** (*Al-Ḥujurāt*: 13).

Pẹ̀lú èyí, *Al-Qur'ān* ń fi rinlẹ̀ pé gbogbo abara ènìyàn, bí ó ti wulẹ̀ kí àwọ̀ wọn àti ìpìlẹ̀ jẹ́, nínú àrọ́mọdọ́mọ Ādam àti Ḥawwā' – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá àwọn méjèèjì – ni wọ́n wà. Àti pé dájúdájú yíyàtọ̀ àti jíjẹ́ oníran-ǹran, èyí tó wà láàrin wọn, kì í ṣe láti gbé ọlá fún ìran kan lórí òmíràn, ṣùgbọ́n ó wà fún dídá ara ẹni mọ̀, bíbá ara ẹni ṣe papọ̀, àti mímáa ran ara ẹni lọ́wọ́, ṣùgbọ́n lílọ́lá àti jíjẹ́ alápọ̀n-ọ̀nlé, ẹni tó bá jọ́sìn fún Ọlọ́hun, tí ó sì bẹ̀rù Rẹ̀ ni ó wà fún.

Kódà *Al-Qur'ān* pé àkíyèsí wa sí pé dájúdájú yíyàtọ̀ àwọ̀ àwọn ènìyàn, ìrísí wọn àti ṣíṣe ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ èdè wọn àti ọ̀làjú wọn, nínú àwọn ìdẹ̀ra Ọlọ́hun àti àwọn àmì Rẹ̀ àti àwọn ohun ènmọ̀ ìṣẹ̀dá Rẹ̀ nínú ayé yìí ni. Ò tún ṣe àfijọ rẹ̀, níbi títóbi rẹ̀ àti pípàtàkì rẹ̀, pẹ̀lú dídá àwọn sánmà àti ilẹ̀. **"Àti pé nínú àwọn Àmì Rẹ̀ ni pé; Ó dá àwọn ìyàwó fún yín látara ẹ̀mí ara yín, nítorí kí ẹ le sinmi sí wọn lọ́dọ̀, Ó sì fi ìfẹ àti àánú sí ààrin yín"** (*Ar-Rūm*: 22)



**Ànábì Muḥammad ni Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn *Islām* rán**

"Ẹ̀yin ènìyàn! Ẹ tétí gbọ́, dájúdájú Ọlọ́hun Ọba yìn, Ọ̀kan ṣoṣo ni, dájúdájú bàbá yín ọ̀kan ṣoṣo ni. Ẹ tétí gbọ́, kò sí ọlá kankan fún Lárúbáwá lórí elédèkedè, bẹ́ẹ̀ ni kò sí fún elédèkedè lórí Lárúbáwá, bẹ́ẹ̀ ni kò sí fún ènìyàn pupa lórí ènìyàn dúdú, bẹ́ẹ̀ ni kò sí fún ènìyàn dúdú lórí ènìyàn pupa, àyàfi pẹ̀lú ìbẹ̀rù Ọlọ́hun"



**Ìkéde kárí-ayé nípa àwọn iwọ̀ ènìyàn**

Èyí tí ó fi dídọ́gba àwọn ènìyàn níbi òmìnira, àwọn ẹ̀tọ́ àti àpọ́nlé rinlẹ̀

630 *CE* — 1948 *CE*

Nígbà tó jẹ́ wí pé, àsìá tó tóbi jùlọ, tó sì jẹ́ àkọ́kọ́, nínú ìkéde kárí-ayé, fún àwọn iwọ̀ ènìyàn, èyí tó fi dídọ́gba àwọn ènìyàn níbi òmìnira, àwọn ẹ̀tọ́ àti àpọ́nlé rinlẹ̀, bíbá òfin mu rẹ̀ wáyé ní ọdún 1948 CE, lẹ́yìn èyí ni ṣíṣe àmúlò rẹ̀ bẹ̀rẹ̀, dájúdájú Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn Islām rán, Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –, síwájú 1400 sẹ́yìn, níti pàápàá, ti kéde rẹ̀ pẹ̀lú ohùn rara. Ó sì fi ìgbà ọ̀tun lọ́lẹ̀ fún àwọn abara ènìyàn, nígbà tó sọ, nígbà tó ń bá àwọn ènìyàn sọ̀rọ̀, pé: **"Ẹ̀yin ènìyàn, ẹ tétí gbọ́; dájúdájú Ọlọ́hun Ọba yín, Ọ̀kan ṣoṣo ni, àti pé dájúdájú bàbáa yín ìkan náà ni, ẹ tétí gbọ́; kò sí ọlá kankan fún Lárúbáwá lórí elédèmìíràn, bẹ́ẹ̀ ni kò sí ọlá kankan fún elédèmìíràn lórí Lárúbáwá, kò sì sí ọlá kankan fún aláwọ̀ pupa lórí aláwọ̀ dúdú tàbí aláwọ̀ dúdú lórí aláwọ̀ pupa àyàfi pẹ̀lú ìbẹ̀rù Ọlọ́hun"** (*Aḥmad*: 23489).

Ẹ̀sìn *Islām* ṣe àgbékalẹ̀ ìwòye fún jíjẹ́ oníran-ǹran àwọn ènìyàn, ní ọ̀nà tí ètò ìṣẹ̀mí-ayé mìíràn kò mọ̀, tí àwọn ìran ènìyàn tí ó wà lórí ilẹ̀ kò sì bá a sáábà.



## Níní àkàkún àwùjọ, ìpín kan nínú ìgbàgbọ́ òdodo ni:

Àwọn àgbélẹ̀rọ ìròrí kan ka ènìyàn sí ọ̀gá pátápátá fún ilé-ayé yìí, èyí tó le máa darí rẹ̀ ní ìbámu sí àǹfààní rẹ̀ àti àwọn ohun tó fẹ́, láìsí ẹnìkankan tí yóò ṣe ìṣirò iṣẹ́ rẹ̀ tàbí olùṣọ́. Kódà kí èyí fa bíba àwọn abala kan nínú ilé-ayé yìí jẹ́, tàbí yóò kó ìparun bá àwọn ìran ẹ̀dá kan. Ní ọ̀nà mìíràn ẹ̀wẹ̀, apákan nínú rẹ̀ kò fún ènìyàn ní pípàtàkì kankan lórí ohun tó yàtọ̀ sí i. Nítorí náà kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe ìran kan nínú àìmọye àwọn ìran ẹ̀dá. Tó bá rí bẹ́ẹ̀, ojú wo wáá ni ẹ̀sìn *Islām* fi wo àjọṣepọ̀ ènìyàn pẹ̀lú ilé-ayé yìí.

Ìwòye ẹ̀sìn *Islām* sí àbùdá àjọṣepọ̀ ènìyàn pẹ̀lú ayé, dá lórí àwọn ìròrí tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ìgbàgbọ́ àti ìwòye. Ó sì parí pẹ̀lú àwọn ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ ìdajọ́ láti de àjọṣepọ̀ pẹ̀lú ènìyàn, ẹranko, ilẹ̀ àti àwọn orísun àdámọ́.

Àkọ́kọ́ ohun tí olùṣewadìí yóò ṣe àkíyèsí rẹ̀, nípa ìròrí tó ní í ṣe pẹ̀lú àjọṣepọ̀ yìí, ni wọ̀ntún-wọ̀nsì, èyí tí *Al-Qur'ān* ṣe ìfirinlẹ̀ rẹ̀. Ọlọ́hun buyì kún ènìyàn, Ó sì ṣe àdáyanrí rẹ̀ yàtọ̀ sí àwọn ẹ̀dá tó ṣẹ́kù. **"Dájúdájú A ti ṣe àpọ́nlé fún àwọn ọmọ (Ànábì) Ādam, A sì gbé wọn gun orí ọ̀dàn àti òkun, A sì pèsè fún wọn nínú àwọn ohun tó mọ́, A sì gbé ọlá fún wọn gidigidi lórí ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú ohun tí A dá"** (*Al-'Isrā'*: 23). Ó tún rọ ilé-ayé yìí fún un àti àwọn ẹ̀dá tó wà ní àyíká rẹ̀, nítorí kí ó le máa fi wọn ṣe àǹfààní, kí ó sì máa ṣe àmójútó wọn. **"Ọlọ́hun ni Ẹni tó dá àwọn sánmà àti ilẹ̀, Ó sì sọ omi kalẹ̀ láti sánmà, Ó sì mú àwọn èso jáde pẹ̀lú rẹ̀ láti máa jẹ́ ìjẹ-ìmu fún yín. Ó sì rọ ọkọ̀ ojú-omi fún yín nítorí kí ó le máa rìn lórí òkun pẹ̀lú Àṣẹ Rẹ̀, Ó tún rọ àwọn odò fún yín (32). Ó tún rọ òòrùn àti òṣùpá fún yín tí wọ́n ń gba iṣẹ́ fún ara wọn, Ó sì rọ òru àti ọ̀sán fún yín"** (*Ibrāhīm*: 32-33). Nítorí náà ènìyàn kì í ṣe ìran kan lásán nínú àìmọye àwọn ìran ẹ̀dá mìíràn, tí kò ní ọlá kankan lórí àwọn ẹ̀dá tó yàtọ̀ sí i, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ẹ̀dá abiyì, alápọ̀n-ọ́nlé, Ọlọ́hun rọ àdámọ́ fún un, nítorí kí ó le máa ṣe àǹfààní pẹ̀lú rẹ̀. **"Òun ni Ẹni tí Ó dá gbogbo ohun tí ń bẹ lórí ilẹ̀ pátápátá fún yín"** (*Al-Baqarah*: 29)

Ṣùgbọ́n ó tún kàn án nípá fún wa, ní ọ̀nà mìíràn, pé dájúdájú kì í ṣe ọ̀gá pátápátá fún ilé-ayé yìí, tí ó le máa ṣe ohun tó bá wù ú níbẹ̀. Àti pé ipò tí a tọ́ka sí yẹn, àti yíyàtọ̀ rẹ̀ sí àwọn ẹ̀dá tó kù, kò fún un ní ẹ̀tọ́ láti máa ba ilẹ̀ jẹ́ àti kíkó ìparun bá àwọn orísun àdámọ́. Nítorí pé Ẹni tó ni gbogbo nǹkan ni Ọlọ́hun, Ọba Adẹ́dàá, ojúṣe ènìyàn àti ipò rẹ̀ kò kọjá pé Ọlọ́hun (fi ṣe àrólé) nínú ilé-ayé yìí lọ. Ìtumọ̀ èyí ni pé; Ó ṣe é ní ẹni tí a sọ àsọtẹ́lẹ̀ fún, ó ní ẹ̀tọ́ ṣíṣe àmúlò àti ṣíṣe àǹfààní, Ó sì pa á láṣẹ láti máa ṣe ìgbìyànjú láti mú ìlọsíwájú àti ìdàgbàsókè bá a, láìsí ìnira tàbí bíbà á jẹ́ láti ọwọ́ ènìyàn tàbí àwọn ẹ̀dá mìíràn yàtọ̀ sí i. **"Sí àwọn ìran Thamūd, A rán arákùnrin wọn Ṣāliḥ. Ó sọ wí pé: Ẹ̀yin ènìyàn mi! Ẹ máa sin Ọlọ́hun, kò sí ọlọ́hun mìíràn fun yín lẹ́yìn Rẹ̀. Òun ni Ó dá yín látara ilẹ̀, tí Ó sì jẹ́ kí ẹ máa ṣẹ̀mí ní orí rẹ̀. Nítorí náà ẹ tọrọ àforíjìn ní ọ̀dọ̀ Rẹ̀, lẹ́yìn náà ẹ ronú pìwàdà lọ sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀. Dájúdájú Ọlọ́hun, Ọba mi jẹ́ Ọba tó súnmọ́, Ọba tó máa ń dáhùn ìpèpè"** {*Hūd*: 61}. **"(Rántí) ìgbà tí Ọlọ́hun, Ọba rẹ sọ fún àwọn *Malā'ikah* pé: Dájúdájú Èmi yóò dá àrólé kan sí orí ilẹ̀, wọn sọ wí pé: Ṣé O fẹ́ dá sí orí rẹ̀; ẹni tí yóò máa ṣe ìbàjẹ́ lórí rẹ̀, tí yóò sì máa ta ẹ̀jẹ̀ sílẹ̀, tí àwa sì ń ṣe àfọ̀mọ́ pẹ̀lú ẹyìn Rẹ, tí a sì ń ṣe àfọ̀mọ́ fún Ọ? Ó (Ọlọ́hun) sọ wí pé: Dájúdájú Èmi mọ ohun tí ẹ̀yin kò mọ̀"** (*Al-Baqarah*: 30).

Òfin ìmọ̀ ẹ̀sìn *Islām*, láti kanpá mọ́ èyí, fi ogunlọ́gọ̀ àwọn òfin àti àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ pẹ̀lú àlàyé kíkún rinlẹ̀, láti fi òǹdè de àjọṣepọ̀ tò gbópọn yìí láàrin ènìyàn àti gbogbo ilé-ayé tó wà ní àyíká rẹ̀. Nínú èyí, ní àpèjúwe, ni:



## 1. Níní àkàkún àwọn ẹranko:

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ wá láti ọ̀dọ̀ Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –, tí ó ń pèpè síbi ṣíṣọ́ iwọ̀ àwọn ẹranko, àti bíbu ẹ̀san rere tí ó tóbi fún ṣíṣe dáadáa sí wọn ní Ọ̀run. Ó kọ̀ nípa fífi ṣùta kàn wọ́n, ó sì ṣe ìlérí àwọn ìyà tó le koko jùlọ láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun lórí rẹ̀

Nígbà tó jẹ́ wí pé dájúdájú àkọ́kọ́ ẹgbẹ́ tó ní àkàkún sí iwọ̀ àwọn ẹranko, wọ́n dá a sílẹ̀, ní ìlú Bírítéènì ní ọdún 1824CE, pẹ̀lú orúkọ: Ẹgbẹ́ ìjọba èyí tó wà fún ẹ̀tọ́ àwọn ẹranko. Àkọ́kọ́ òfin, èyí tí a mọ̀ ní ayé òde-òní, tó ka títayọ ààlà lórí àwọn ẹranko, sí ìwà ọ̀daràn, wọ́n fi ẹsẹ̀ rẹ̀ rinlẹ̀ ní ìlú Bírítéènì ní ọdún 1949CE. Dájúdájú ẹ̀sìn *Islām* síwájú ohun tó ju ọgọ́rùn-ún ọdún mẹ́rìnlá lọ, ti ṣe títayọ ààlà lórí àwọn ẹranko ní ẹ̀ẹ̀wọ̀, ó sì kà á sí ìwà ọ̀daràn. Ó tún mẹ́nu ba ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn àpèjúwe rẹ̀ nínú ọlọ́kan-ò-jọ̀kan ọ̀rọ̀ tó wá láti ọ̀dọ̀ Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –. Bíi ṣíṣe fífi ebi pa ẹranko ní ẹ̀ẹ̀wọ̀, tàbí fífa ìyà jẹ é, tàbí gbígbé ohun tí ipá rẹ̀ kò ká lé e lórí, tàbí fífi ṣeré ní ọ̀nà tí yóò kó ṣùtá bá a, tàbí títí kan nína án ní ojú! Àti àwọn ìdájọ́ mìíràn tó gbajúmọ̀ nínú àwọn tírà àgbọ́yé ẹ̀sìn *Islām*.

Bóyá òǹkàwé yóò mọ̀ bí ẹ̀sìn *Islām* ti ṣe àkàkún níní áánú pẹ̀lú àwọn ẹranko tó, nígbà tó bá rí ọ̀rọ̀ Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – nígbà tí ó ń fún àwọn ènìyàn ní ìrò pé: Dájúdájú obìnrin kan tó ti sọ ṣíṣe aṣẹ́wó di iṣẹ́ (èyí sì jẹ́ ara àwọn ohun tí jíjẹ́ ẹ̀ẹ̀wọ̀ rẹ̀ le koko jùlọ nínú ẹ̀sìn *Islām*) rí ajá kan tó ti fẹ́ kú nítorí òǹgbẹ, ìṣesí rẹ̀ ṣe é ní àánú, ó bọ́ bàtà rẹ̀, ó sì rọ omi sí i láti inú kọ̀nga, lẹ́yìn náà ó fún ajá náà ní omi mu, nítorí náà Ọlọ́hun ṣe àforíjìn fún un. **"Láàrin ìgbà tí ajá kan ń rọkiriká kọ̀nga, tí òǹgbẹ ti fẹ́ẹ̀ pa á, ní ọ̀kan nínú àwọn obìnrin aṣẹ́wó ọmọ Ísírẹ́lì bá rí i, ó sì bọ́ ìbọ̀sẹ̀ aláwọ rẹ̀, ó sì fún un ní omi mu, nítorí náà Ọlọ́hun sì ṣe àforíjìn fún un"** (*Al-Bukhārī:* 3280).



Àkọ́kọ́ àgbékalẹ̀ òfin láti ka kíkọjá ààlà lórí àwọn ẹranko sí ìwà-ọ̀daràn wáyé ní ìlú Bírítéènì ní ọdún 1949CE

Àkọ́kọ́ ẹgbẹ́ tó wà fún ẹ̀tọ́ àwọn ẹranko wáyé ní ọdún 1824CE

Ẹ̀sìn *Islām* ṣe fífi ebi pa ẹranko, tàbí fífi ìyà jẹ é, tàbí gbígbé ẹrù tó ju agbára rẹ̀ lọ lé e lórí, tàbí fífi ṣeré ní ọ̀nà tí yóò kó ìpalára bá a, ní èèwọ̀ ní ọdún 632CE

## 2. Níní àkàkún àwọn irúgbìn:

Ẹ̀sìn *Islām* gbà wá níyànjú lórí Níní àkàkún àwọn irúgbìn àti ṣíṣe ọ̀gbìn, bóyá èyí jẹ́ nítorí àǹfààní ara ẹni, tàbí ti ẹlòmìràn nínú àwọn ènìyàn àti àwọn ẹ̀dá mìíràn nínú ilé-ayé yìí!

Nínú rẹ̀ ni ohun tí Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – fún wa ní ìró nípa rẹ̀ pé dájúdájú ẹnì kankan kò ní gbin nǹkankan tàbí kí ó kópa níbi mímú ohun tí yóò ṣe àwọn ẹ̀dá ní àǹfààní jáde nínú ilẹ̀, kí ẹyẹ wá jẹ nínú rẹ̀, tàbí èèyàn, tàbí ẹranko, àyàfi kí ohun tó ṣe yìí jẹ́ ìtọrẹ-àánú fún un. **"Kò sí Mùsùlùmí kankan tí yóò lọ́ nǹkan, tàbí kí ó gbin irúgbin kan, àyàfi kí ohun tó ṣe yìí jẹ́ ìtọrẹ-àánú fún un"** (Al-Bukhārī: 2320).

Kódà dájúdájú Ànábí alápọ̀n-ọ́nlé, pe Mùsùlùmí, ní ìgbà tí nǹkan bá díjú àti ìgbà tí nǹkan bá le koko jùlọ, síbi pé kò gbọdọ̀ fi ìgbìyànjú kankan pamọ́ nípa níní àkàkún àwùjọ, mímú ìdàgbàsókè bá ilẹ̀ àti mímú un gbèrú pẹ̀lú ṣíṣe ọ̀gbìn, kódà kí ó dá a lójú pé òun kò ní ṣe àǹfààní nínú rẹ̀, nígbà tó sọ wí pé: Tí Ìgbẹ́nde bá tó – ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó tóbi jùlọ ní ilé-ayé – tí ohun tí ẹnìkan nínú yín fẹ́ lọ̀ sì wà lọ́wọ́ rẹ̀, ó pọndandan lórí rẹ̀ kí ó yára lọ̀ ọ, tí ó bá lágbára rẹ̀, kí ó le jẹ́ ìtọrẹ-àánú fún un. **"Tí àsìkò Ìgbẹ́nde bá tó, tí ohun tí ẹnìkan nínú yín fẹ́ lọ̀ sì wà lọ́wọ́ rẹ̀, tí ó bá lágbára láti lọ̀ ọ kí ó tó tó, kí ó rí i pé ohun ṣe bẹ́ẹ̀"** (*Aḥmad*: 12981).

Ó ṣe gbígbé orí ilẹ̀ àti mímáa mú ìdàgbàsókè bá a ní ara àwọn àfojúsùn àti àwọn ìjọsìn ní ìgbà tí nǹkan bá díjú àti ìgbà tí nǹkan bá le koko jùlọ, nǹkankan, bí ó ti wulẹ̀ kó tóbi tó, kò gbọdọ̀ gbé wa kúrò níbẹ̀.

## 3. Níní àkàkún àwọn orísun àdámọ́:


Ẹ̀sìn *Islām* kanpá mọ́ ṣíṣe àmójútó àwujọ, àti àìkò ìparun bá àwọn orísun rẹ̀, tàbí kò ìdọ̀tí bá a àti bíbà á jẹ́, ó sì ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ètò tí ń gbé ara wọn nígbọ̀wọ́ fún àwọn ènìyàn, èyí tí ó dúró lórí ìpìlẹ̀ (wíwá ìṣọ́ra síwájú wíwá ìtọ́jú), nínú èyí ni: Kíkanpá mọ́ ìmọ́tótó ara ènìyàn àti níní àkàkún sí ìfọ́síwẹ́wẹ́ rẹ̀, àti ṣíṣe àmójútó àwọn orísun àdámọ́, àti níní wọ̀ntún-wọ̀nsì níbi lílò ó, àti kíka bíbà á jẹ́ àti kíkó ẹrẹ̀ bá a sí ìwà pòkíì, nínú àwọn àpèjúwe èyí ni:

- Ó ṣe yíya àpà, níbi lílo àwọn orísun àdámọ́, ní èèwọ̀. Àkọ́kọ́ rẹ̀ ni lílo omi, kódà kó jẹ́ pẹ̀lú èròńgbà ìjọsìn fún Ọlọ́hun níbi àlùwàlàá (èyí tí í ṣe fífọ̀ àwọn oríkèé ara kan síwájú ìrun).
- Ó kọ̀ fún àwọn alágbára àti àṣẹ láti máa kó àwọn orísun àdámọ́ pamọ́, ní ọ̀nà tó le fa ìnira fún àwọn ẹlòmíràn. Nítorí náà ó ṣe kíkó omi pamọ́ ní èèwọ̀ (gẹ́gẹ́ bíi àpèjúwe fún àwọn orísun àdámọ́) àti (gẹ́gẹ́ bíi àpèjúwe fún agbára) àti koríko (gẹ́gẹ́ bíi àpèjúwe fún oúnjẹ) (*Abū Dāwd*: 3477).

> Níní àkàkún àwùjọ àti kíkópa níbi fífọ̀ ọ́ mọ́ kúrò níbi ìdọ̀tí, jẹ́ ìpín kan nínú ìgbàgbọ́ òdodo, gẹ́gẹ́ bí Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn *Islām* rán ti sọ.

- Ó kọ̀ nípa ohun tí ó le ba àwùjọ jẹ́ ní àyíká wa, nínú àwọn àpèjúwe èyí ni; kíkọ̀ nípa títọ̀ sínú omi adégún, nítorí pé yóò kó ẹ̀gbin bá a, àti nípa ṣíṣe ìgbọ̀nsẹ̀ sí àwọn ààyè tí ìbòji wà àti àwọn ojú-ọ̀nà, nítorí pé ó jẹ́ àwọn ààyè tí àwọn ènìyàn máa ń tọ̀, tàbí pé àwọn tí ń rékọjá máa ń lọ síbẹ̀ láti sinmin níbi wàhálà ìrìn-àjò àti ìnira ìrìn.

Gbogbo èyí kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe àwọn àpèjúwe péréte, kì í ṣe ohun tí ó le ṣe ènìyàn ni èǹmọ̀ nípa ẹ̀sìn kan tó jẹ́ wí pé Ìránṣẹ́ alápọ̀n-ọ́nlé tí Ọlọ́hun fi rán, ka fífọ̀ àwùjọ mọ́ kúrò níbi àwọn ìdọ̀tí, àti kíkópa níbi ṣíṣe àtúnṣe pẹ̀lú mímú ohun tí ó le ṣe ènìyàn ní ṣùtá kúrò ní ojú-ọ̀nà, sí pé kì í ṣe iṣẹ́ dáadáa lásán, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ẹka kan lára pàápàá ìgbàgbọ́ òdodo (*Muslim*: 35).



## Ẹ̀sìn ìmọ̀:

Kì í ṣe èèsì ni pé àkọ́kọ́ gbólóhùn *Al-Qur'ān*, èyí tí Ọlọ́hun sọ̀kalẹ̀ fún Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – ni: (Kà). Dájúdájú àwọn kíkan ọ̀rọ̀ nípá wá nínú *Al-Qur'ān* alápọ̀n-ọ́nlé àti àwọn ọ̀rọ̀ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – lórí ìkúnlọ́wọ́ tí ẹ̀sìn *Islām* ṣe fún gbogbo ìmọ̀ tí ó ṣe àǹfààní fún àwọn abara ènìyàn. Títí tí ó fi jẹ́ wí pé ọ̀nà tí Mùsùlùlmí ń tọ̀ láti wá ìmọ̀ àti òye, òun náà ni ọ̀nà tí yóò tọ̀ wọ ọgbà-ìdẹ̀ra Al-Jannah. Gẹ́gẹ́ bí Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – ti sọ wí pé: **"Ẹnikẹ́ni tó bá tọ ọ̀nà kan; tí ó ń wá ìmọ̀- ẹ̀sìn níbẹ̀, Ọlọ́hun yóò tìtorí rẹ̀ rọ ọ̀kan nínú àwọn ọ̀nà ọgbà-ìdẹ̀ra Àlùjáńnà fún un"** (*Muslim* 2699).

Nínú àfiwé tó ya ènìyàn lẹ́nu, èyi tí Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun alápọ̀n-ọ́nlé ṣe àlàyé rẹ̀ pẹ̀lú ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé: Dájúdájú ọlá tí ń bẹ fún onímímọ̀ lórí ẹni tó takú tí ṣíṣe ìjọsìn (láìsí ìmọ̀), ó dà gẹ́gẹ́ bíi ọlá tí ń bẹ fún Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun alápọ̀n-ọ́nlé, Muḥammad, tí a bá fi wé ènìyàn tó kéré jùlọ ní ọlá. **"Ọlá tí ń bẹ fún onímímọ̀ lórí olùjọsìn dà gẹ́gẹ́ bíi ọlá tí ń bẹ fún mi lórí ẹni tó kéré jùlọ nínú yín"** (*At-Tirmidhī*: 2685).

Fún ìdí èyí, ẹ̀sìn *Islām* kò mọ ogun kankan láàrin ẹ̀sìn àti ìmọ̀ gẹ́gẹ́ bí ó ti wà nínú àwọn ẹ̀sìn mìíràn. Wọn kò sì gbé ìdájọ fún àwọn onímímọ̀ lórí àwọn ìròrí àti àwọn àbájáde ìmọ̀ tó ní í ṣe pẹ̀lú àdámọ́, gẹ́gẹ́ bí ó ti wà ní àwọn ayé-dúdú, ṣùgbọ́n ní ìdàkeji èyí pátápátá, ẹ̀sìn ni àtùpà ìmọ̀, òun ni ń ràn án lọ́wọ́, òun ni ó ń pèpè sí i; nípa kíkọ́ àti fífi kọ́ ènìyàn. Àwọn Mọ́ṣáláṣì sì jẹ́ ààyè gíga fún oríṣiríṣi àwọn ìmọ̀ àti àgbọ́yé, ní òpin ìgbà tí oore bá ti wà níbẹ̀ fún àwọn ènìyàn.

Kò le ṣe wa ní èǹmọ̀, nígbà náà, kí ó jẹ́ wí pé ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àwọn onímímọ̀ nípa àdámọ́ tí wọ́n jẹ́ Mùsùlùmí, wọ́n bẹ̀rẹ̀ ìṣẹ̀mí àyé wọn pẹ̀lú kíkọ́ *Al-Qur'ān* àti híhá a àti wíwá ìmọ̀ nípa àgbọ̀yé ẹ̀sìn, lẹ́yìn náà wọ́n lààmì-laaka níbi àwọn agbagbe ìmọ̀ tó jindò, èyí tí wọ́n yàn láàyò.

Dájúdájú Ọlọ́hun ṣe àpọ́nlé fún ipò onímímọ̀ tó ń kọ́ àwọn ènìyàn ní dáadáa, Ó sì dé e ní adé ní ọ̀nà tó ga jùlọ, títí tí Ànàbí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – fi sọ wí pé gbogbo ẹ̀dá ní yóò máa ṣe àdúà fún ẹni tó ń kọ́ àwọn ènìyàn ní dáadáa. **"Dájúdájú Ọlọ́hun, àwọn *Malā'ikah* Rẹ̀, àwọn ará sánmà àti ilẹ̀ tìtí kan èèrà tó wà nínú ihò rẹ̀ àti títí kan ẹja, níti páàpàá, yóó máa ṣe àdúà fún ẹni tó ń kọ́ àwọn ènìyàn ní dáadáa"** (*At-Tirmidhī:* 2685).

**"Àwọn tó pọ̀ jùlọ nínú àwọn onímímọ̀ nípa àdámọ́ àti iṣẹ́-ìṣẹ̀gùn, tí wọ́n jẹ́ Mùsùlùmí, bẹ̀rẹ̀ ìṣẹ̀mí-ayé wọn pẹ̀lú kíkọ́ *Al-Qur'ān*, èyí tó pè wọ́n lọ síbi jíjindò níbi àwọn ìmọ̀ mìíràn.**

**Nínú àwọn onímímọ̀ àwọn Mùsùlùmí:**



1. ***Al-Khawārizmī* (790-850 Baghdād),** ó jẹ́ onímímọ̀ nípa ìmọ̀ ìṣirò, ìmọ̀-ẹ̀rọ àti ìmọ̀ nípa ojú-ọjọ́, òun ni ẹni tó dá ìmọ̀ wíwá ojútùú sí ìṣirò tó dojú rú sílẹ̀, òun ni wọ́n kọ́kọ́ tú àwọn ìwé rẹ̀ sí èdè mìíràn fún àwọn ọ̀làjú mìíràn. Kódà àwọn gbólóhùn èdè Lárúbáwá, *Al-Jabr (Algebra), Aṣ-ṣifr* (Zero) wọnú àwọn èdè Latin nítorí rẹ̀.



2. ***Ibn Al-Haytham* (965- 1040 Cairo)** onímímọ̀ nípa ìmọ̀ Físíìsì àti ìmọ̀ ẹ̀rọ, èyí tó so mọ́ Mọ̣sálásí gboogbò *Azhar*. Ó ṣe àwọn ìgbìyànjú tó tóbi jùlọ níbi àwọn ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ tó ní í ṣe pẹ̀lú ìtọ́jú ojú. Wọ́n sì máa ń fi àwọn ìpìlẹ̀ ṣíṣe kámẹ́rà tì sí i. Àwọn tó pọ̀ jùlọ nínú àwọn aṣèwadìí fi rinlẹ̀ pé gbólóhùn kámẹ́rà, èyí tó ti tàn ká nínú ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ èdè, kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe gbólóhùn *(qumrah)* nínú èdè Lárúbáwá, èyí tí í ṣe orúkọ yàrá ìmọ́lẹ̀, èyí tí *Ibn Al-Haytham* ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀.



3. ***Al-Bayrūnī* (973-1048 ìlú Khuwārizm),** àgbà onímímọ̀ nípa ojú-ọjọ́, òun ni àkọ́kọ́ ẹni tó sọ pé ilẹ̀ ń yípo ìlà rẹ̀, ó sì tọ́ka sí agbára tí ń fa ilẹ̀.





4. ***Az-Zahrāwī* (936- 1013 Spain),** dókítà Mùsùlùmí tó jẹ́ onísẹ́ abẹ, èyí tí iṣẹ́-abẹ gbòòrò láti ọwọ́ rẹ̀, dé ibi pé ó ṣe àdásílẹ̀, ó sì ṣàlàyé ogunlọ́gọ̀ àwọn irinṣẹ́ abẹ nínú àwọn ìwé rẹ̀. Àwọn ìwé rẹ̀ sì padà di ìpìlẹ̀ kan gbògíì nínú ìmọ̀-ìwòsàn àti iṣẹ́-abẹ fún àìmọye ọrúndún ọdún lẹ́yìn èyí pẹ̀lú oríṣiríṣi èdè.



5. ***Ibn Sīnā* (980-1037 ìlú Bukhārā),** èyí tí wọ́n mọ̀ láàrin àwọn onímọ̀-ìjìnlẹ̀ sí (Avicenna), dókítà, ọ̀jọ̀gbọ́n tí ó gbajúmọ̀, òun ni ẹni tó síwájú àwọn ènìyàn àsìkò rẹ̀ níbi ṣíṣe àlàyé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ohun tó súyọ nípa ìmọ̀ iṣẹ́-ìṣègùn, àti àlàyé ìwòsàn rẹ̀. Bẹ́ẹ̀ náà ni ó tún gbé ọlà fún ipò níní ìrírí níbi ìmọ̀-ìjìnlẹ̀, níbi àwọn iṣẹ́-ìwadìí rẹ̀, àti àwọn ẹ̀kọ́ ìmọ̀-ìṣègùn rẹ̀, èyí tó mú un dé ibi àwọn àwárí-ìmọ̀ tó jindò, èyí tó jẹ́ kí ó gbawájú mọ́ àwọn ènìyàn àsìkò rẹ̀ lọ́wọ́, tó sí ṣẹ́kù títí di ayé òde-òní. Èyí yóò hàn kedere nínú ìwé rẹ̀ (Al-Qānūn), èyí tó jẹ́ ibùsẹ́rísí gbògíì nípa kíkọ́ ìmọ̀-ìṣègùn fún ọrúndún méje, kíkọ́ ọ sì tẹ̀síwájú ní àwọn ilé-ẹ̀kọ́ gíga àwọn Òyìnbó títí di ààrin ọrúndún kẹtàdínlógún.

Dájúdájú lẹ́yìn tí ó ti gbajúmọ̀ pẹ̀lú ìmọ̀ iṣẹ́-ìṣègùn tán, ó máa ń tọ́jú àwọn ènìyàn ní ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bíi ìwòye ìjọ́mọnìyàn láti ọ̀dọ̀ rẹ̀, àti láti fi dúpẹ́ fún Ọlọ́hun lórí ìmọ̀ àti òye tí Ó fún un.



6. ***Ibnu-Nafīs* (1213-1288 ìlú Dimashq),** ó jẹ́ ara àwọn onímímọ̀ nípa òfin ẹ̀sìn àti ìmọ̀ àgbọ́yé ẹ̀sìn *Islām*, bákan náà ó tún jẹ́ ara àwọn onímímọ̀ tó tóbi jùlọ nípa iṣẹ́-ìṣègùn, àti ìmọ̀ iṣẹ́ àwọn oríkèé ara nínú ìtàn. Òun ni àkọ́kọ́ ẹni tó ṣe àwárí tó mọ̀yán lórí nípa yíyípo ẹ̀jẹ̀ tí ó kéré jùlọ, ó sì ṣàlàyé rẹ̀. Ó tún ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ìròrí tó ní í ṣe pẹ̀lú iṣẹ́-ìṣègùn, èyí tí wọn ò yé máa lo ọ̀pọ̀lọpọ̀ rẹ̀ títí di àsìkò yìí.

## Ẹ̀sìn *Islām* kó gbogbo agbegbe ìgbésí-ayé ènìyàn sínú:

Ó máa ń jẹ́ iyàlẹ́nu fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn ènìyàn, nígbà tí wọ́n bá mọ̀ pé ẹ̀sìn *Islām* kò mọ lórí àwọn ètò ìjọsìn, àwọn iṣẹ́ àti àwọn ìgbaniníyànjú kárí-ayé lásán gẹ́gẹ́ bí ó ti wà nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ẹ̀sìn, èyí tí wọ́n ti bá sáábà.

Nítorí náà, ẹ̀sìn *Islām*, níti papa, kì í ṣe bùkáátà ẹ̀mí, èyí tí àwọn Mùsùlùmí yóò máa gbọ́ nínú àwọn Mọ̀ṣáláṣí pẹ̀lú àdúà ṣíṣe àti ìrun kíkí lásán.

Bákan náà, kì í ṣe ògédé àwọn ìrorí, àwọn àdìsọ́kàn àti ìwòye, èyí tí àwọn tó ń tẹ̀lé e kàn ní ìgbàgbọ́ nínú rẹ̀ lásán.

Gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ wí pé kì í ṣe ètò ọrọ̀-ajé lásán, tàbí ètò àwùjọ, èyí tó ń gbé ara wọn nígbọ̀wọ́..

Kì í ṣe àwọn òfin, àti àwọn ìwòye tó wà fún ṣíṣe àgbékalẹ̀ ètò àti àwùjọ lásán..

Bẹ́ẹ̀ náà ni kì í ṣe àkójọpọ̀ àwọn ìwà àti àwọn ìhùwàsí nípa bí a ṣe máa ń bá àwọn ẹlòmíràn lò..

Ṣùgbọ́n ó jẹ́ ìlànà tó pé fún gbogbo agbegbe ìṣẹ̀mí-ayé, ní ọ̀nà-kọnà tí ó le pín sí, àti gbogbo ẹka rẹ̀. Gbogbo èyí àti òmíràn ni ó kó sínú. Síbẹ̀síbẹ̀, kò de òmìnira àwọn ènìyàn pẹ̀lú ìwọ̀nba ohun tí ìṣẹ̀mí-ayé wọn bá ṣe ní ìrọ̀rùn fún wọn, nítorí kí wọn le da ojú gbogbo ìgbìyànjú wọn kọ ṣíṣe ohun meremere, kíkọ́lé àti ọ̀làjú. Èyí sì jẹ́ ọ̀kan nínú ìdẹ̀ra tó tóbi jùlọ, èyí tí Ọlọ́hun máa ń fi ṣe ìrègún lórí àwọn ẹrúsìn Rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí *Al-Qur'ān* tí kànpa mọ́ ọn. (*Al- Mā'idah*: 3).

Nígbà tí ènìyàn kan, tí kì í ṣe Mùsùlùmí, sọ –ní ẹni tí ń ṣe yẹ̀yẹ́ – fún ọ̀kan nínú àwọn sààbé Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun alápọ̀n-ọ́nlé – orúkọ rẹ̀ ni *Salmān Al-Fārisī* – pé: Dájúdájú ẹni yín (Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun ni ó gbà lérò) ń kọ́ yín ní gbogbo nǹkan tití dé orí àwọn ẹ̀kọ́ títọ̀ àti yíyàgbẹ́?! Sààbé pàtàkì yìí fún un ní èsì pé: Bẹ́ẹ̀ ni, dájúdájú ó kọ́ wa. Lẹ́yìn náà, ó sọ àwọn ìdájọ́ ẹ̀sìn *Islām* àti àwọn ẹ̀kọ́ rẹ̀ nípa ọ̀ràn yìí fún un. **"Bẹ́ẹ̀ ni. Dájúdájú ó kọ̀ fún wa nípa kí á da ojú kọ gábàsì fún ìgbẹ́ tàbí ìtọ̀, tàbí kí á máa táábà pẹ̀lú ọwọ́ ọ̀tún, tàbí kí á ṣe ìmọ́ra pẹ̀lú òkúta tí ó dín sí mẹ́ta, tàbí kí á ṣe ìmọ́ra pẹ̀lú ìgbẹ̀ ẹran tàbí egungun"** (*Muslim*: 262).



### Ayé àti ọ̀run:

Àwọn ara àtijọ́, ní ìlú *Miṣr*, máa ń tú tùràrí sí òkú lára, lẹ́yìn náà wọn yóò kó àwọn ohun-ìní rẹ̀ tó bá níye lórí pẹ̀lú rẹ̀, wọ́n lérò pé dájúdájú ó bùkáátà sí i níbi ìṣẹ̀mì ọrun rẹ̀ lẹ́yìn ikú.

Ní ọ̀nà mìíràn, àwọn ènìyàn kan nínú ìran Tabit máa ń gé okú wọn wẹ́lẹ́wẹ̀lẹ̀, wọn yóò sì gbé e sí àwọn ààyè gíga fún àwọn ẹyẹ àti àwọn ẹranko abijà. Àwọn ẹlẹ́sìn *Hindūsiyyah*, kò yé máa jó òkú wọn níná, nítorí pé dájúdájú èyí, ní ìbámu sí ìgbàgbọ́ wọn, ni ọ̀nà kan ṣoṣo tó wà láti la ẹ̀mí wọn.

> Ṣùgbọ́n ó jẹ́ ìlànà tí ó pé fún gbogbo agbegbe ìṣẹ̀mí-ayé, ní ọ̀nà-kọnà tí ó le pín sí, àti gbogbo ẹka rẹ̀.



Gbogbo èyí kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe àwọn àpèjúwe ráńpẹ́, fún àwọn oríṣiríṣi ètò ìjọsìn sísin òkú àti bíbá a dágbére, èyí tó yapa ara wọn, tó yàtọ̀ sí ara wọn, láti ìgbà dégbà àti ààyè dááyè, ní ìbámu sí ẹ̀sìn, àdìsọ́kàn àwọn ènìyàn nípa ohun tó wà lẹ́yìn ikú, àti àwọn ohun tó hàn nípa àwọn ìbéèrè, èyí tó jindò, èyí tó ń wá èsì.. Ṣé ìṣẹ̀mí mìíràn ń bẹ? Báwo ni yóò ti rí? Kín ni ohun tí a bùkáátà sí níbẹ̀?

Èyí rí bẹ́ẹ̀, nítorí pé dájúdájú ikú, òhun ni pàápàá tí ó tóbi jùlọ, èyí tí gbogbo kálukú wa panupọ̀ pé ó ń retí gbogbo wa pátápátá, láìsí àyàfi kankan, bóyá a jẹ́ ẹni tó gbàgbọ́ nínú ìṣẹ̀mí mìíràn (lẹ́yìn ikú), tàbí àwọn àgbìyèlé wa kò kọjá ohun tí à ń rí, tí a sì ń fura mọ̀ pẹ̀lú àwọn irinṣẹ́ ìfuramọ̀ tí Ọlọ́hun dá mọ́ wa .., àti pé bóyá a jẹ́ ẹni tí ó múra sílẹ̀ fún àsìkò ìṣẹ́rípadà yìí, tàbí a gbìyànjú láti ṣe bíi ẹni tí ó gbàgbé rẹ̀ àti bíi ẹni tí ó gbàgbéra nípa rẹ̀ pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ohun eré àti àwọn ohun tí ó máa ń kó àìrójú bá ènìyàn.

Yóò wá ṣẹ́ku ìbéèrè, èyí tí yóò gbógun ti gbogbo ìran àìmọ̀kan àti ìgbàgbé, tí ó sì kọ̀ àyàfi kí ó máa jẹyọ làti ìgbà dégbà, ní gbogbo ìgbà tí ènìyàn bá ti kóra ró, tí ó ń ronú sí ọ̀ràn ara rẹ̀.. Ṣé èyí ni òpin, kò sí nǹkankan mọ́? Ṣé bíbẹ wa ìran kan nínú eré ni bí?

Ìbéèrè kan ń bẹ tí ó máa rankankan mọ́ lààkàyè wa ní ọ̀pọ̀ ìgbà, tí *Al-Qur'ān* sí máa ń pààrà rẹ̀ ní oríṣiríṣi ọ̀nà. Ní àsìkò yìí kan náà, ó tún ń fún wa ní ìró nípa ṣíṣe àbàmọ̀ àti ìbànújẹ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn ènìyàn ní ọjọ́ Ìgbẹ́nde, nítorí pé dájúdájú wọn kò kó ẹ̀mí ara wọn ró láti fèsì sí ìbéèrè yìí, wọn kò sì pèsè kalẹ̀ fún ìrìn-àjò. Nítorí náà apákan wọn, nígbà náà, yóò sọ wí pé: Áà! Kílódé tí mi ó ti ti (iṣẹ́ dáadáa) síwájú fún ìṣẹ̀mí mi? **"Yóò máa wí pé: Áà! Kílódé tí mi ó ti ti (iṣẹ́ dáadáa) síwájú fún ìṣẹ̀mí mi?"** (*Al-Fajr*: 24).

Ẹlòmíràn yóò sì sọ wí pé: Kílódé tí mi ò ti di iyẹ̀pẹ̀. **"Dájúdájú Àwa ni A ti kìlọ̀ ìyà kan tí ó súnmọ́ fun yín, ní Ọjọ́ ti ènìyàn yóò máa wo ohun ti ọwọ́ rẹ̀ méjèèjì tì síwájú, tí aláìgbàgbọ́ yóò sì máa wí pé: Áà! Kílódé tí mi ò ti di iyẹ̀pẹ̀"** (*An-Naba'*: 40).

Nínú ohun tí a ti mọ̀ ni pé gbogbo àwọn ẹlẹ́sìn tó wá láti sánmà ní ìgbàgbọ́ pẹ̀lú ìṣẹ̀mí Ọ̀run, àti ẹsan rere àti ìyà inú rẹ̀, nítorí pé dájúdájú èyí ni ohun tí gbogbo àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun mú wá dá lé lórí. Àti nítorí pé dájúdájú lààkàyè jẹ́rìí sí i pé dájúdájú ìṣẹ̀mí-ayé, ẹ̀sìn àti àwọn ìwà kò ní ìtumọ̀ kankan láìsí ìṣẹ̀mí mìíràn, tí iṣiro iṣẹ́ yóò wà níbẹ̀, tí gbogbo ènìyàn yóò sì gba ẹ̀san rẹ̀ níbẹ̀, bóyá rere ni tàbí aburú.



Síbẹ̀síbẹ̀, ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn ènìyàn máa ń lérò pè dájúdájú ẹ̀sìn àti ìjọsìn, kò rọrùn kò papọ̀ pẹ̀lú ṣíṣiṣẹ́ owó tàbí wíwá ìgbádùn tàbí ìdàgbàsókè. Nítorí náà nínú kí iṣẹ́ jẹ́ ti ayé tàbí kí ó jẹ́ ti Ọ̀run, ṣùgbọ́n kò rọrùn kí méjèèjì pàdé papọ̀ ní àsìkò kan náà, gẹ́gẹ́ bí òru àti ọ̀sán kò ṣe le pàdé papọ̀. Àsìkò, nínú kí ó jẹ́ èyí tàbí ìyẹn..

Ṣíṣe èèmọ̀ wọn kò le dé òpin, kódà ó nira fún apákan nínú wọn láti gbàgbọ́ pé dájúdájú gàgá yìí, èyí tó wà láàrin ìjọsìn àti ìgbádùn, ní àpèjúwe, tàbí èyí tó wà láàrin ìjọsìn àti owó, kò sí nínú ìgbàgbọ́ tí ẹ̀sìn *Islām* mú wá.. Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun alápọ̀n-ọ́nlé, Muḥammad, fun wá ní ìró pé dájúdájú tí ènìyàn bá ṣe ohun tó ṣe déédé, bí ó ti wulẹ̀ kí agbegbe rẹ̀ jẹ́, tó sì gba dáadáa lérò pẹ̀lú rẹ̀, dájúdájú wọn yóò san án lẹ́san rere lórí ohun tó ṣe yìí ní Ọ̀run, kódà kí ó jẹ́ wí pé èyí kò ju ẹ̀gún tí ó mú kúrò ní ojú-ọ̀nà lọ, tàbí títí kan òkèlè oúnjẹ tí ó ń fi sí ìyàwó rẹ̀ lẹ́nu (*Al-Bukhārī*: 56).

Nígbà tí Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun alápọ̀n-ọ́nlé, Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – fun wá ní ìró pé dájúdájú àwọn ọ̀nà tí a máa ń gbà ṣe dáadáa pé oríṣiríṣi, kò ní òpin, ó fi nǹkankan ṣe àpèjúwe, èyí tí ó fa iyàlẹ́nu fún àwọn sàábé rẹ̀, nígbà tí ó sọ wí pé: Nígbà tí ẹnikẹ́ni nínú yín bá gbádùn ara rẹ̀ pẹ̀lú ìyàwó rẹ̀, wọn yóò kọ ẹ̀san rere sílẹ̀ fún un. Àwọn sàábé rẹ̀ sọ wí pé: Kín ni àjọsepọ̀ tó wà láàrin ẹ̀san rere àti adùn? Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun alápọ̀n-ọ́nlé sì dáhùn pé: Ẹ sọ fún mi ná, tí ó bá gbádùn ara rẹ̀ pẹ̀lú ohun tó jẹ́ èèwọ̀, ṣé kò ní gba ẹ̀ṣẹ̀? Wọ́n wí pé: Bẹ́ẹ̀ ni. Ó wí pé: Ìdí nìyẹn tí wọn yóò fi kọ ẹ̀san rere sílẹ̀ fún un nígbà tí ó bá gba ọ̀nà tó tọ́. (*Muslim*: 1006).

Ìdí nìyí, tí ó fi jẹ́ wí pé gbogbo ẹni tí ó bá ń wá ìmọ̀ nípa ẹ̀sìn *Islām*, láti ìgbà àkọ́kọ́, yóò ṣe àkíyèsí pàápàá wọ̀ntún-wọ̀nsì láàrin ìṣẹ̀mí ayé àti ìṣẹ̀mí Ọ̀run, gẹ́gẹ́ bí *Al-Qur'ān* tí ń yàwòrán rẹ̀. Nígbà tí ó ń gba àwọn ènìyàn níyànjú lórí ṣíṣe ìjọsìn láti fi wá ẹ̀san rere ní Ọ̀run, ní àsìkò yìí kan náà, ó tún kanpá mọ́ gbígbìyànjú ní ayé láti wá Ọlá Ọlọ́hun. **"Ẹyin ẹni tó gbàgbọ́ lódodo! Nígbà tí wọ́n bá pèpè fún ìrun ní ọjọ́ àkójọ (*Jumu'ah*), nígbà náà ẹ yára lọ síbi Ìrántí Ọlọ́hun, kí ẹ sì pa òwò tì. Ìyẹn ni ó lóore jùlọ fun yín tí ó bá jẹ́ pé ẹ mọ̀ ni (9). Àti pé nígbà tí wọ́n bá parí ìrun, ẹ yáa fọ́nká lórí ilẹ̀, kí ẹ sì máa wá nínú Ọlá Ọlọ́hun, kí ẹ sì rántí Ọlọ́hun ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ nítorí kí ẹ le jèrè"** (*Jumu'ah*: 9-10). Pẹ̀lú èyí, yóò tún ní ẹ̀tọ́ sí ẹ̀san rere, ní òpin ìgbà tí ó bá ti gba wíwá ojú rere Ọlọ́hun lérò pẹ̀lú iṣẹ́ náà. Àti pé Mùsùlùmí jẹ́ ẹni tí wọ́n pa láṣẹ pẹ̀lú pé kí ó máa jọ́sìn fún Ọlọ́hun pẹ̀lú ìgbìyànjú rẹ̀ níbi iṣẹ́-òòjọ́ rẹ̀ àti iṣẹ́ rẹ̀ tí ó fi ń wá ìjẹ-ìmu rẹ̀, títọ́ àwọn ọmọ rẹ̀, níní àkàkún rẹ̀ sí àlàáfíà ara rẹ̀ àti àwùjọ rẹ̀, àti mímú ìlọsíwájú bá àwùjọ rẹ̀, gẹ́gẹ́ bí yóò ti máa jọ́sìn fún Un pẹ̀lú ìrun rẹ̀, ìtọrẹ-àánú rẹ̀ àti gbígba ààwẹ̀ rẹ̀.

Èyí ni ọ̀kan nínú àwọn àṣírí ìfàyàbalẹ̀ ẹ̀mí àti àlàáfíà àtinúwá, èyí tí Mùsùlùmí máa ń rí nígbà tó bà fura mọ̀ àjọṣepọ̀ tó wà láàrin ìṣẹ̀mí-ayé rẹ̀ àti ọ̀run rẹ̀ àti láàrin ìgbádùn rẹ̀ àti ìjọsìn rẹ̀, nìtorí náà kò sí àtakò, kò sì sí àìbáré, ṣùgbọ́n méjèèjì jẹ́ ilé tí a mọ, tó ń gbé ara wọn nígbọ̀wọ́, tí apákan sì ń ran apákejì lọ́wọ́.

Látara èyí ni *Al-Qur'ān* ti kanpá mọ́ àmì-ìdánimọ̀ Mùsùlùmí fún wa, èyí tí ó kó ìròrí ẹ̀sìn *Islām* nípa ìyẹn sínú, pẹ̀lú pípa á láṣẹ pé kí ó kéde rẹ̀ pẹ̀lú ohùn rara pé: Dájúdájú gbogbo ìṣẹ̀mí-ayé mi, ìjọsìn fún Ọlọ́hun ni, pẹ̀lú gbogbo àwọn ìṣesí rẹ̀. Kì í ṣe ìrun mi àti ìjọsìn mi nìkan ni ó wà fún Ọlọ́hun, ṣùgbọ́n gbogbo àwọn ìṣesí ìṣẹ̀mí-ayé mi pátápátá, mò ń rankàn ẹ̀san rere lórí rẹ̀ ní ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun. Òun náà ni yóò sì padà dájọ́ lórí àwọn iṣẹ́ mi, yóò sì san mí lẹ́san lórí rẹ̀ lẹ́yìn ikú mi. Pẹ̀lú èyí ni màá fi jẹ́ ẹni tí ó dúnní mọ́ Àṣẹ Ọlọ́hun àti ẹ̀sìn Rẹ̀, èyí tí í ṣe ẹ̀sìn *Islām*. **"Wí pé: Dájúdájú ìrun mi, ẹran pípa mi, ìṣẹ̀mí mi àti ikú mi, fún Ọlọ́hun ni, Ọlọ́hun Ọba gbogbo àgbáyé"** {*Al-'An'ām*: 162}.



## Ẹ̀sìn ìbára ẹni ṣe àti ṣíṣe àṣepọ̀:

Àlàyé ọlọ́pọ̀lọpọ̀ ìrìn-àjò Mùsùlùmí; Aḥmad ọmọ *Faḍlān*, fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ agbègbè ìlú Rọ́ṣíà, Dẹ́ńmáàki, *Iskandnāfiyah*, ni wọ́n kà sí ìròyìn àkọ́kọ́ tí ó múnàdóko, àti àlàyé tí ó kún fún ìṣẹ̀mí ènìyàn àti bí àwùjọ ti rí, èyí tí gbogbo àgbàyé padà mọ̀ nípa àwọn ìlú wọ̀nyí.

Ìdí èyí ni pé Aḥmad ọmọ *Faḍlān*, ní ọdún 921*CE* ṣe ìrìn-àjò kan tó ya ènìyàn lẹ́nu, èyí tí a le kà sí ara àwọn ìrìn-àjò kíkàn sí ara ẹni ti ọ̀làjú ní àwọn orúndún àárin gùngùn. Dájúdájú ó jáde láti ìlú *Baghdād* – èyí tó jẹ́ olú-ìlú ìmọ̀-ìjìnlẹ̀ àti ọ̀làjú nígbà náà –, ó sì rékọjá pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn ìlú àti àwọn ìran. Ó sì fi ẹ̀rí gbe àwọn ohun tó fi ojú rí àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀, èyí tó wáyé ní àsìkò rẹ̀, lẹ́sẹ̀ nínú ìwé kan tó kún kẹ́kẹ́, èyí tí wọ́n tẹ̀ jáde fún ìgbà àkọ́kọ́ ní ọdún 1923, ní ìbámu sí ẹ̀dà àpilẹ̀kọ, èyí tí wọ́n rí ní ìlú Rọ́ṣíà.

Ìdí tí ìwé ọmọ *Faḍlān* fi pàtàkì, gẹ́gẹ́ bí onímimọ̀, tó jẹ́ ọmọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà; *Michael Crichton*, ti sọ ni pé; dájúdájú àwọn Mùsùlùmí, ní ìlú *Baghdād*, pẹ̀lú bí wọ́n ti wawọ́ koko mọ́ ẹ̀sìn wọn tó, wọ́n jẹ́ ẹni tó tẹ́ra sílẹ̀ fún àwọn ìran mìíràn tó yàtọ̀ sí wọn níbi ìrísí, ìlànà àti àdìsọ́kàn. Wọ́n tún jẹ́ ìran tí ilẹ̀ rẹ̀ kéré jùlọ nígbà náà. Èyí ni ó sọ wọ́n di ẹlẹ́rìí, ènìyàn tó dá yàtọ̀ fún àwọn ọ̀làjú àtọ̀húnrìnwá.

*Michael Crichton (Eaters of the Dead)*

Ẹ̀sìn *Islām* pèpè sí ìfọwọ́-sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àwọn ènìyàn lórí mímọ ayé, ọ̀làjú, àtúnṣe, rírọ̀pọ̀ mọ́ wọn àti mímáa bá wọn ṣe papọ̀ pẹ̀lú àwọn ìwà ẹ̀wà tí ó ga jùlọ àti ìjẹ́-ọmọlúàbí ní ọ̀nà-kọ̀nà tí ọ̀làjú àti ẹ̀sìn wọn le pín sí. Ó tún ta wá jí sí pé yíyẹra àti jíjìnnà sí àwọn ènìyàn kì í ṣe ìlànà ẹ̀sìn *Islām* tó ní àlàáfíà. Nítorí èyí ni Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – fi ka ẹni tó máa ń rọ̀pọ̀ mọ́ àwọn ènìyàn, tó sì máa ń ṣe sùúrù lórí ohun tí ó bá a nínú ṣùtá àti àṣìṣe wọn sí ẹni tó dára ju ẹni tó ń yẹra fún wọn, tó sì máa ń jìnnà sí wọn lọ (*Ibn Mājah*: 4032).



# Àdẹ́dàá kan ṣoṣo.. Ẹni tí à ń jọ́sìn fún kan ṣoṣo

## Ẹ̀sìn


Ẹ̀sìn *Islām* kàn án nípá pé, dájúdájú níní ìwòye nípa àdìsọ́kan Mùsùlùmí, kò tó láti wọnú ìgbàgbọ́ òdodo. Nítorí pé tí ó bá jẹ́ wí pé Ọ̀kan ṣoṣo ni Ọlọ́hun, Ọba Adẹ́dàá, a jẹ́ wí pé Ọ̀kan ṣoṣo ni Ọlọ́hun tí à ń jọ́sìn fún gbọdọ̀ jẹ́.

## Gbólóhùn (Allāh) túmọ̀, nínú èdè Lárúbáwá, sí ìtumọ̀ mẹ́ta papọ̀:

- Ó túmọ̀ sí Ẹni tí à ń jọ́sìn fún, Ẹni tí àwọn ènìyàn ń ṣe àfọ̀mọ́ ìrun wọn àti ààwẹ̀ wọn fún, àti àdojúkọ ọkàn wọn àti gbogbo ìjọsìn wọn.
- Ẹni tó tóbi níbi pàápàá Rẹ̀, àwọn ìròyìn Rẹ̀ àti gbígbọngbọ́n Rẹ̀, débi wí pé àwọn làákàyè ń pòruurù nípa títóbi Rẹ̀, wọ́n sì kágara láti rọkiri Rẹ̀ ní ìmọ̀.
- Ẹni tí àwọn ọkàn ń so mọ́, tí àwọn ẹ̀mí ń jẹ̀rán Rẹ̀, tí yóò sì máa balẹ̀ pẹ̀lú ìrántí Rẹ̀, tí yóò sì máa gbádùn pẹ̀lú sísúnmọ́ Rẹ̀ àti jíjọ́sìn fún Un.

*Al-Qur'ān* tún kan án nípá pé dájúdájú, ó pọndandan kí á ṣe àtúnṣe ìròrí wa nípa (Allāh), kí á sì fọ̀ ọ́ mọ́ kúrò níbi gbogbo àwọn àyípadà àti àwọn àdápa iró, èyí tó ń kó àbùkù bá pípàtàkì Ọlọ́hun àti títóbi Rẹ̀..

Nítorí náá, Ọlọ́hun, gẹ́gẹ́ bí *Al-Qur'ān* ti ń ṣàlàyé, Òun ni Adẹ́dàá, Olùṣẹ̀dá ayé yìí àti ètò rẹ̀. Gbogbo ohun tí ń ṣẹlẹ̀ nínú rẹ̀, bí ó ti wulẹ̀ kí ó kéré tó, ẹ̀dá Rẹ̀ ni í ṣe, ó sì ń bẹ pẹ̀lú Èròǹgbà Rẹ̀, ìpèbùbù Rẹ̀ àti Ìmọ̀ Rẹ̀. Abo kankan nínú gbogbo ìran ẹ̀dá kò le ní oyún, kò sì le bímọ àyàfi pẹ̀lú Ìmọ̀ Rẹ̀ àti Èròǹgbà Rẹ̀. Omi òjò kankan kò sìle kán sílẹ̀, ìyípadà kankan kò le ṣẹlẹ̀ ní òru tàbí ọ̀sán, ní gbangba tàbí kọ̀rọ̀, ní ààyèkáàyè ní ilé-ayé yìí, àyàfi kí Ọlọ́hun rọkiriká rẹ̀ ní ìmọ̀, agbára àti ìkẹ́. **"Ọ̀dọ̀ Rẹ̀ ni wọn yóò dá ìmọ̀ Àsìkò padà sí. Àti pé nǹkankan nínú àwọn èso kò ní jáde kúrò nínú apópó rẹ̀, obìnrin kankan kò sì ní lóyún, tàbí kí ó bímọ, àyàfi pẹ̀lú Ìmọ̀ Rẹ̀. Àti pé ni Ọjọ́ tí yóò pè wọ́n pé: Níbo ni àwọn òòṣà (tí ẹ̀ ń pè ní) akẹgbẹ́ Mi wà? Wọn yóò wí pé: A ń fi mọ̀ Ọ́ (Ìrẹ Ọlọ́hun wa) pé kò sí olùjẹrìí kankan (lórí ijẹ Ọlọ́hun wọn) nínú wa"** (Fuṣṣilat: 47). **"Àti pé ọ̀dọ̀ Rẹ̀ ni àwọn kọ́kọ́rọ́ ìkọ̀kọ̀ wà, ẹnìkankan kò mọ̀ wọ́n àyàfi Òun níkan. Ó sì mọ ohunkóhun tó wà lórí ọ̀dàn àti nínú òkun. Ewéko kankan kò sì ni jábọ́ àyàfi kí Ó mọ̀ ọ́n. Kò sì sí hóró irúgbìn kan nínú àwọn òkùnkùn ilẹ̀, tàbí ohun tútù ni, tàbí ohun gbígbẹ àyàfi kí ó wà nínú Tírà tí ó fojú hàn"** (*Al-'An'ām*: 59).



*Al-Qur'ān* kan án nípá pé dájúdájú gbogbo nǹkan máa ń ṣẹlẹ̀ pẹ̀lú Ìmọ̀ Ọlọ́hun àti Agbára Rẹ̀, títí kan àwọn èkíkán omi òjò àti jíjábọ̀ àwọn ewé igi.



> Ohun tí ó fojú hàn gbangba jùlọ nínú ẹ̀sìn *Islām* ni jíjẹ́ ọranyàn ṣíṣe àfọ̀mọ́ ìjọsìn fún Ọlọ́hun nìkan ṣoṣo yàtọ̀ sí ẹlòmíràn. Èyí ni ìpèpè gbogbo àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun gẹ́gẹ́ bí *Al-Qur'ān* ti kanpá mọ́ ọn.

Ó ń bẹ fún Un, mímọ́ ni fún Un, nínú àwọn ìròyìn, èyí tó dára jùlọ nínú rẹ̀, èyí tó pé jùlọ nínú rẹ̀ àti èyí tó rẹwà jùlọ nínú rẹ̀. Òun ni Alágbára, Ẹni tí ohun kankan kò le borí Rẹ̀, Ọba àṣàkẹ́ ọ̀run, Ẹni tí ìkẹ́ Rẹ̀ kárí gbogbo nǹkan, Òun ni Ọba tí Ó tóbi, Ẹni tí àbùkù kankan kò le bá A ní ọ̀nà-kọnà.

Nígbà tí apákan nínú àwọn ènìyàn ń sọ wí pé; dájúdájú Ọlọ́hun dá àwọn sánmà àti ilẹ̀ ní ọjọ́ mẹ́fà, lẹ́yìn náà Ó sinmin ní ọjọ́ keje, *Al-Qur'ān* dé, ó sì ba gbogbo àwọn èròkerò yìí jẹ́, ó sọ ọ́, pẹ̀lú gbogbo àlàyé tó hàn kedere pé: **"Dájúdájú A ti dá àwọn sánmà àti ilẹ̀ àti gbogbo ohun tó wà láàrin àwọn méjèèjì ní ọjọ́ mẹ́fà, agara kankan kò sì dá Wa"** (èyí tùmọ̀ sí ìnira). (*Qāf*: 38). Ó tún ṣàlàyé pé èròkerò yìí àti àwọn ohun tó jọ ọ́, kò déédé wá sí làákàyè ènìyàn bíkòṣe nítorí ṣíṣe àfijọ Ọlọ́hun pẹ̀lú ohun tí làákàyè mọ̀ nínú àwọn ẹ̀dá. Ṣùgbọ́n Òun, mímọ́ ni fún Un, ni Adẹ́dàá, ẹ̀dá ni gbogbo ohun tí ó yàtọ̀ sí I. Báwo wáá ni ẹ̀dá yóò ṣe jọ Ẹni tó dá a? **"Kò sí ohun kankan tí ó dà bíi irú Rẹ̀, àti pé Òun ni Olùgbọ́rọ̀, Olùríran"** (*Ash-Shūrā*: 11).

Òun, mímọ́ ni fún Un, ni Adájọ́, Onídéédé, Ẹni tí kò le ṣe àbòsí ohun tó mọ bíi ìwọn ọmọ-ináagún. Ohun tí à ń rí nínú ìṣẹ̀mí-ayé, nínú rẹ̀ ni Ó ti ń fi ọgbọ́n Rẹ̀ àti àánú Rẹ̀ hàn wá. Gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ wí pé, ó máa ń pamọ́ fún ọmọdé; apákan nínú àwọn ìgbésẹ̀ àwọn òbí rẹ̀ méjèèjì, tí kò ní le gbọ́ ọ yé, tàbí ṣe àlàyé rẹ̀, nítorí títóbi ìyàtọ̀ tó wà láàrin wọn níbi níní ìkápá láti ronú. Nítorí náà mímọ àwọn nǹkankan, ọgbọ́n tí Ọlọ́hun fi sí abẹ́ apákan nínú àwọn ẹ̀dá Rẹ̀ àti Èròǹgbà Rẹ̀, le bọ́ mọ́ làákàyè ènìyàn lọ́wọ́.

Ẹ̀sìn *Islām* kò fi mọ sórí èyí nìkan, nígbà tó ń fi rinlẹ̀ pé; àdìsọ́kàn ìwòye, kò tó láti wọ inú ìgbàgbọ́ òdodo. Nítorí náá, tó bá jẹ́ wí pé Ọ̀kan ṣoṣo ni Ọlọ́hun Ọba, Aṣẹ̀dá, a jẹ́ wí pé Ọ̀kan ṣoṣo ni Ọlọ́hun tí a ó ma jọ́sìn fún gbọdọ̀ jẹ́. Dídojú nǹkankan nínú ìjọsìn tàbí àdúà kọ ohun tó yàtọ̀ sí Ọlọ́hun, kò ní àlááfìà, ṣùgbọ́n a gbọdọ̀ ṣe àfọ̀mọ́ ìjọsìn fún Un, mímọ́ ni fún Un, láìsí alàgàta tàbí olùṣìpẹ̀. Ọba Aṣẹ̀dá tóbi, Ó sì pàtàkì ju bẹ́ẹ̀ lọ

Tí ó bá jẹ́ wí pé ọba tàbí olórí ìlú, ní ilé-ayé, kò rọrùn fún un láti mọ àwọn ẹni tó bùkáátà sí ìrànlọ́wọ́ àti àwọn ọ̀lẹ, lẹ́yàn náà kí ó dé ọ̀dọ̀ wọn, àyàfi láti ipasẹ̀ àwọn tó ń ràn án lọ́wọ́, àwọn tó ń bá a ṣiṣẹ́ àti àwọn tó súnmọ́ ọn, tí wọ́n wà fún ṣíṣe àlàyé ìṣesí àwọn tó ń dà jẹ fún un, kí ó le ràn wọ́n lọ́wọ́, kí ó sì nawọ́ áánú sí wọn, ṣùgbọ́n Ọlọ́hun, mímọ́ ni fún Un, mọ gbangba àti ohun tó pamọ́. Òun ni Alágbára, Òun ni Ó ni gbogbo nǹkan, Òun ni Ó ní ìkápá lórí gbogbo nǹkan, Ọwọ́ Rẹ̀ àti abẹ́ dídarí Rẹ̀, ni gbogbo ilé-ayé pátá wà, dájúdájú àṣẹ Rẹ̀, nígbà tí Ó bá gbèrò nǹkankan ni kí Ó sọ fún pé: Jẹ́ bẹ́ẹ̀! Yóò sì jẹ́ bẹ́ẹ̀.. kín ni yóò wá fa dídojúkọ ohun tó yàtọ̀ sí I?

*Al-Qur'ān* tún fi rinlẹ̀ pé dájúdájú níní ìfọ̀kànbalẹ̀ àti ìfàyàbalẹ̀, kò le pé, kò sì le parí, ní òpin ìgbà tí Mùsùlúmí kò bá ti máa wá ọ̀nà-àbáyọ lọ sí ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun Ọba rẹ̀, ní ẹni tí ó gbé gbogbo bùkáátà rẹ̀ sí iwájú Rẹ̀, Òun náà sì ni Alágbára, Ọba tí Ó tóbi, Ọba tí Ó fẹ́ràn àwọn ẹrùsìn Rẹ̀, Aláàánú sí wọn, Ọba tí Ó súnmọ́ wọn, Ẹni tí Ó máa ń dunnú pẹ̀lú pípè É tí àwọn ẹrùsìn Rẹ̀ ń pè É, yóò sì pọ́n wọn lé, yóò sì tún san wọ́n lẹ́san ní ìbámu sí bí sísádi wọn àti títẹ̀ríba wọn fún Un bá ti mọ. **"Kílódé tí ẹ̀ ń**

**ṣe àìgbàgbọ́ sí Ọlọ́hun tí ó sì jẹ́ wí pé okú ni yín tẹ́lẹ̀, Ó sì sọ yín di alàààyè. Lẹ́yìn náà yóò pa yín, lẹ́yìn náà yóò sọ yín di alàààyè, lẹ́yìn náà, ọ̀dọ̀ Rẹ̀ ni wọn yóò da yín padà sí"** (*Al-Baqarah*: 28). **"Àbí Ẹni tí ń jẹ́pè ẹni tí ara ń ni nígbà tí ó bá pè É, tí Ó sì ń ká aburú kúrò, tí Ó sì fi yín ṣe àwọn àrólé ilẹ̀? Ṣé ọlọ́hun kankan ń bẹ pẹ̀lú Ọlọ́hun ni? Díẹ̀ ni ẹ máa ń rántí. 63- Àbí Ẹni tí ń fi yín mọ̀nà nínú àwọn òkùnkùn ọ̀dàn àti òkun, àti Ẹni tí ń rán àwọn atẹ́gùn ní ìró ìdùnnú síwájú Àánú Rẹ̀ (òjò)? Ṣé ọlọ́hun kankan ń bẹ pẹ̀lú Ọlọ́hun ni? Gíga fún Ọlọ́hun kúrò níbi ohun tí wọ́n ń fi ń ṣẹbọ (pẹ̀lú Rẹ̀)"** (*An-Naml*: 62-63).

Ohun tí ó fojú hàn gbangba jùlọ nínú ẹ̀sìn *Islām* ni jíjẹ́ ọ̀ranyàn ṣíṣe àfọ̀mọ́ ìjọsìn fún Ọlọ́hun nìkan ṣoṣo yàtọ̀ sí ẹlòmíràn. Gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́hun, Ọba tí ọlá Rẹ̀ ga, ti wí pé: **"Àti pé dájúdájú A ti gbé Ìránṣẹ́ dìde sí gbogbo ìjọ kọ̀ọ̀kan pé: Ẹ sin Ọlọ́hun, ẹ sí jìnnà sí òrìṣà"** (*Naḥl*: 36). Èyí ni ìpèpè gbogbo àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun gẹ́gẹ́ bí *Al-Qur'ān* ti kanpá mọ́ ọn. Kò sí Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun kankan, kò sí ọ̀kan nínú àwọn *Malā'ikah*, kò sí ẹni Ọlọ́hun kankan, bí ó ti wulẹ̀ kí jíjẹ́ ẹni dáadáa rẹ̀ tó, tí a gbọdọ̀ ṣẹ́rí nǹkankan nínú àwọn ìran àdúà sí, pẹ̀lú àwáwí pé wọ́n jẹ́ alàgàta láàrin Ọlọ́hun àti àwọn ẹrúsìn Rẹ̀.. nítorí pé dájúdájú, ní ìparí ọ̀ràn, ẹ̀dá Ọlọ́hun  ẹrúsìn Rẹ̀ ni gbogbo wa. Ọlọ́hun sì súnmọ́ àwọn ẹrúsìn Rẹ̀, Ó gbọ́ ń ọ̀rọ̀ wọn, Ó sì ń dáhùn ìpèpè wọn, ní òpin ìgbà tí wọ́n bá ti ṣe àfọ̀mọ́ ìjọsìn fún Un, mímọ́ ni fún Un.

Báwo ni kò ṣe ni rí ìtọ́wò orìire; ẹni tí ó ṣe àfọ̀mọ́ àdojúkọ rẹ̀ sí ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun? Kò sí fífọ́n yẹ́lẹyẹ̀lẹ, kò sì sí dàrúdàpọ̀. Nítorí pé Ọ̀kan ni Ẹni tí Ó ni gbogbo nǹkan, Ọ̀kan ni Adẹ́dàá, Ọ̀kan ni Ẹni tí à ń jọ́sìn fún, àdojúkọ àti sísádi, ọ̀dọ̀ Rẹ̀, mímọ́ ni fún Un, nìkan ni a máa ń darí rẹ̀ sí, yàtọ̀ sí ohun tí ó yàtọ̀ sí I.

Èyí ni ìtumọ̀ *Sūrah* kékere kan nínú àwọn Sūrah  *Al-Qur'ān* tí ó tóbi jùlọ, tí ó sí gbajúmọ̀ jùlọ. Èyí ni *Sūratul-'Ikhlāṣ*.


### *Sūratul-'Ikhlāṣ*

Ọlọ́hun pa Ànábì Rẹ̀; Muḥammad, láṣẹ pé kí ó polongo rẹ̀, ní gbogbo ọ̀nà tó fojú hàn kedere, bíi ẹni pé ó ń fèsì sí ìbéèrè yìí pé: Ta gan-an ni Ọlọ́hun?

- Dájúdájú Ọlọ́hun, Ọ̀kan ṣoṣo ni, kò sí orogún fún Un níbi ìjọsìn
- Ọlọ́hun, Òun ni Ẹni tí gbogbo ẹ̀dá ń gbára lé, tí wọ́n sì ń sádi láti wá àwọn ohun tí wọ́n bùkáátà sí.
- Dájúdájú Ó mọ́ kọjá kí Ó ni ọmọ, tàbí kí ó jẹ́ wí pé wọ́n bí I ni. Òun ni Àkọ́kọ́ tí nǹkankan kò bẹ síwájú rẹ̀.
- Kò ní ojúgbà tàbí àfijọ níbi Pàápáà Rẹ̀ àti àwọn Ìròyìn Rẹ̀, nítorí pé Òun ni Adẹ́dàá, ẹ̀dá ni gbogbo ohun tí ó yàtọ̀ sí I.








## Àjọṣepọ̀ tó wà láàrin òfin àdámọ́ àti òfin ìdájọ́ ẹ̀sìn Ọlọ́hun

Ọlọ́hun ṣẹ̀dá ayé yìí, èyí tí à ń gbé inú rẹ̀, ní ìbẹ̀rẹ̀, pẹ̀lú ohun tó pasófo kékeré nínú ara wa àti ohun tó kéré jù ú lọ, ṣùgbọ́n ní ìparí, pẹ̀lú àwọn ihò tó jìnnà jùlọ – èyí tí àwọn ìrinṣẹ́ tí a fi máa ń mú nǹkan súnmọ́ lágbara láti yàwòrán rẹ̀ – pẹ̀lú ṣíṣe nǹkan dáadáa tó dé òpin, àti kí nǹkan máa pé ara wọn àti ètò tó ya ènìyàn lẹ́nu, èyí tí ìṣẹ̀mí-ayé àti àdámọ́ kò rọrùn àyàfi pẹ̀lú rẹ̀. Gbogbo àwọn onímímọ̀ nípa àdámọ́ kan pá mọ́ ọn pé; dájúdájú èyíkéyìí ààyẹ tó bá bá ètò yìí, kódà kó mọ bíńtín, láìsí iyèméjì níbẹ̀, yóò kó ìparun àti títán bá ènìyàn..

Mùsùlùmí gbàgbọ́ pé dájúdájú Adẹ́dàá, Ẹni tí Ó pilẹ̀ dídá ètò-ayé tí ó yani lẹ́nu yìí, pẹ̀lú mímúnádóko rẹ̀ àti ṣíṣe é dáadáa, Òun ni Ẹni tí Ó mọ ohun tí ó dára jùlọ fún àwọn ẹ̀dá Rẹ̀, nínú àwọn òfin ẹ̀sìn, àwọn ìdájọ́ àti ètò ìṣẹ̀mí-ayé. Ẹ̀sìn, èyí tí Ó ṣe ní òfin, òhun ni ètò kan ṣoṣo, èyí tí ó dára fún ìṣẹ̀mí-ayé abara ènìyàn, nínú rẹ̀ sì ni yóò ti là níbi gbígbẹ́rúgbọnrí apákan lórí apá kejì.. Dájúdájú Ọlọ́hun, nígbà tí Ó ń ṣàlàyé, nínú *Al-Qur'ān*, pé; dájúdájú Ẹni tí Ó dá ayé àti abara ènìyàn, Òun ni Ó mọ̀ jùlọ pẹ̀lú ohun tí ó le ṣe àtúnṣe wọn, wí pé: **"Ṣe Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá kò wa ní mọ̀ bí? Àti pé Òun ni Alàánú, Arínúróde"** (*Al-Mulk*: 14).



## Kò sí jíjẹ́ alagbà nínú ẹ̀sìn *Islām*

A ó rí i pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀sìn (yàtọ̀ sí ẹ̀sìn *Islām*) ni ó gbé ọlá nínú ẹ̀sìn fún àwọn ènìyàn pàtàkì kan lórí elòmíràn yàtọ̀ sí wọn, tí ó sì so ìjọsìn àwọn ènìyàn àti ìgbàgbọ̀ wọn mọ́ ìyọ́nú àwọn ènìyàn pàtàkì wọ̀nyẹn àti ìfọwọ́sí wọn. Àwọn (ènìyàn pàtàkì) yẹn – ní ìbamu sí àwọn ẹ̀sìn yìí – ni alàgàta láàrin wọn àti Ọlọ́hun. Àwọn ni wọ́n máa ń ṣe àforíjìn ẹ̀ṣẹ̀ àwọn ènìyàn, kódà wọ́n tún le mọ ìkọ̀kọ̀ – gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ pé èyí ni àpèmọ́ra ìbàjẹ́ wọn –, wọ́n sì máa ń ka yíyapa wọn sí okùnfà òfò tí ó fi ojú hàn.

Ṣùgbọ́n ẹ̀sìn *Islām*, kò sí nínú rẹ̀ rara; iṣẹ́ kankan tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ ènìyàn ẹ̀sìn. Dájúdájú ó pọ́n ènìyàn lé, ó sì gbé ipò rẹ̀ ga, nítorí náà ó là á kúrò níbi jíjẹ̀gàba ẹ̀mí, èyí tí yóò jẹ́ alàgàta láàrin rẹ̀ àti Ọlọ́hun. Fún ìdí èyí, ó ba lílérò pé oríire ènìyàn, tàbí gbígba ìrònúpìwàdà rẹ̀, tàbí ìjọsìn rẹ̀, jẹ́ ohun tí a so mọ́ àwọn ènìyàn kan pàtó, bí ó ti wulẹ̀ kí ọla àti dáadáa wọn tó, jẹ́.

Bẹ́ẹ̀ náà ni ó tún là á kúrò níbi jíjẹ̀gàba ìmọ̀, èyí tó ń lérò pé dájúdájú ìmọ̀ ẹ̀sìn ṣẹ̀ṣà pẹ̀lú rẹ̀ yàtọ̀ sí ohun tó yàtọ̀ sí i. A ó rí i pé dájúdájú *Al-Qur'ān* kò ṣe mímọ̀ nípa ẹ̀sìn àti gbígbọ́ ìtumọ̀ *Al-Qur'ān* yé ní ẹ̀tọ́ fún gbogbo ènìyàn lásán, ṣùgbọ́n ó kà á sí ara àwọn ohun tó ṣe ọ̀ranyàn lé wọn lórí, nígbà tó pa gbogbo Mùsùlùmí láṣẹ mímáa ka *Al-Qur'ān*, gbígbọ́ ọ yé, ríronú sí àwọn ìtumọ̀ rẹ̀, lẹ́yìn náà mímú un lò **{(Eléyìí ni) Tírà, A sọ̀ ọ́ kalẹ̀ fún ọ, ó jẹ́ oníbùkún, nítorí kí wọ́n le ronú sí àwọn Ẹsẹ-ọ̀rọ̀ rẹ̀, àti pé kí àwọn onílàákàyè le rántí}** (*Ṣād*: 29).

Ẹ̀sìn *Islām* pọ́n ènìyàn lé, ó sì gbé ipò rẹ̀ ga, nítorí náà ó là á kúrò níbi jíjẹ̀gàba ẹ̀mí, èyí tí yóò jẹ́ alàgàta láàrin rẹ̀ àti Ọlọ́hun. Fún ìdí èyí, ó ba lílérò pé oríire ènìyàn, tàbí gbígba ìrònúpìwàdà rẹ̀, tàbí ìjọsìn rẹ̀, jẹ́ ohun tí a so mọ́ àwọn ènìyàn kan pàtó, bí ó ti wulẹ̀ kí ọla àti dáadáa wọn tó, jẹ́.



Àwọn ìjọsìn àti ìgbàgbọ́ òdodo máa ń wà láàrin ènìyàn àti Ọlọ́hun Ọba rẹ̀, kò sì ọlá tàbí ìjẹ́-alárinà fún ẹnìkankan nínú àwọn ènìyàn níbẹ̀. Nítorí pé Ọlọ́hun, mímọ́ ni fún Un, súnmọ́ àwọn ẹrúsìn Rẹ̀, Ó ń gbọ́ àdúà ẹrúsìn Rẹ̀, yóò dá a lóhùn, Ó sì ń rí ìjọsìn rẹ̀ àti ìrun rẹ̀, yóò san án lẹ́san rere lórí rẹ̀. Kò sí ẹnìkankan, nínú àwọn ènìyàn, tí ó ní ẹ̀tọ́ láti ṣe àforíjìn tàbí gba ìrònúpìwàdà. Nígbà tí ẹrúsìn Ọlọ́hun bá ti ronúpìwàdà, tí ó sì ṣe àfọ̀mọ́ ọkàn rẹ̀ fún Ọlọ́hun, Ọlọ́hun yóò gba ìrònúpìwàdà rẹ̀, yóò sì ṣe àforíjìn fún un. Nítorí náà, Ọlọ́hun súnmọ́ gbogbo ẹ̀dá nígbà tí wọ́n bá da ojú kọ Ọ́, tí wọ́n sì pè É, gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́hun ti sọ nínú *Al-Qur'ān* pé: **"Àti pé ti àwọn ẹrúsìn Mi bá bi ọ́ ní ìbéèrè nípa Mi, dájúdájú Èmi súnmọ́, mo máa ń dáhùn ìpe olùpèpè nígbà tí ó ba pè Mí. Kí wọ́n yáa dáhùn ìpè Mi, kí wọ́n sì gbà Mí gbọ́, kí wọ́n o le baà mọ̀nà"** (*Al-Bhukhārī*: 186).



*Al-Qur'ān* fi rinlẹ̀ pé dájúdájú Ọlọ́hun súnmọ́ gbogbo ẹ̀dá nígbà tí wọ́n bá da ojú kọ Ọ́, tí wọ́n sì pè É.

### Ṣé ìlànà àrà ọ̀tọ̀ kan ń bẹ fún wíwọnú ẹ̀sìn *Islām* bí?

Kò sí ìlànà tó le koko kankan fún gbígbà ẹ̀sìn *Islām*, fún ẹni tó bá ti tẹ́ lọ́rùn. Kò pọn dandan kí èyí ó wáyé ní ààyè kan pàtó tàbí níwájú àwọn ènìyàn kan pàtó. Ṣùgbọ́n ó ti tó o, nígbà tó bá fẹ́ ṣe èyí, kí ó sọ gbólóhùn ìjẹ́rìí méjèèjì, pẹ̀lú mímọ ìtumọ̀ rẹ̀ àti níní àmọ̀dájú nípa rẹ̀, àti títẹríba fún àwọn ohun tó tọ́ka sí. Gbólóhùn ìjẹ́rìí méjèèjì nìyì:

- Mo jẹ́rìí pé kò sí ọlọ́hun kankan tó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn àyàfi Ọlọ́hun Allāh nìkan (èyí túmọ̀ sí pé: Mo jẹ́rìí, mo sì gbàgbọ́ pé kò sí ọlọ́hun kankan tó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn àyàfi Ọlọ́hun Allāh nìkan, nítorí nàá màá máa jọ́sìn fún Òun nìkan ṣoṣo, kò sí orogún fún Un.)
- Mo sì jẹ́rìí pé Ànábì Muḥammad, níti pàápàá, jẹ́ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun (èyí túmọ̀ sí pé: Mo jẹ́rìí pé Ànábì Muḥammad, níti pàápàá, jẹ́ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun sí gbogbo ènìyàn pátápátá, ..ní ẹni tó ń tẹ̀lé àwọn àṣẹ rẹ̀, tó ń jìnnà sí àwọn ohun tó kọ̀ nípa rẹ̀, àti kí ń máa jọ́sìn fún Ọlọ́hun ní ìbámu sí ohun tó ṣe ní òfin àti ìlànà Rẹ̀.



# Àwọn wo gan-an ni Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun òtítọ́?

Ọlọ́hun

Ọlọ́hun dá àwọn èniyàn nítorí mímáa jọ́sìn fún Un, Ó sì rán àwọn Ìránṣẹ́ sí wọn, kí wọ́n le kọ́ wọ̀n ní òfin ẹ̀sìn Ọlọ́hun, kí wọ́n sì máa rán wọn létí nípa ẹ̀sìn Rẹ̀, wọ́n ń ṣiṣẹ́ láti ṣe àtúnṣe ẹ̀sìn àwọn èniyàn àti ayé wọn, àti nítorí kí wọ́n le jẹ́ àwòkọ́ṣe dáadáa fún àwọn ìjọ wọn, kí wọ́n sì ṣígun sí yíyẹ̀sẹ̀ kúrò níbi ẹ̀sìn Ọlọ́hun, kí wọ́n sì máa pe àwọn èniyàn sí ojú-ọ̀nà tí ó ṣe déédé, nítorí kí ó má baà ṣe sí àwíjàre kankan fún àwọn èniyàn lórí fífi ìgbàgbọ́ òdodo sílẹ̀.. Nítorí náà kín ni pàápàá àwọn Ìránṣẹ́ wọ̀nyí?

## Jíjẹ́ abara Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun:

*Al-Qur'ān*, nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn āyah, kanpá mọ́ ọn pé dájúdájú gbogbo àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun pátápátá, abara ènìyàn ni wọ́n, Ọlọ́hun ṣà wọ́n lẹ́ṣà pẹ̀lú iṣẹ́-ìránṣẹ́ àti ìjẹ́-ìránṣẹ́ Ọlọ́hun. Pẹ̀lú jíjọ ara ẹni níbi jíjẹ́ ènìyàn, èyí tó wà láàrin àwa àti àwọn Ànábì, ṣùgbọ́n dájúdájú wọ́n wà ní ipò tó ga nínú mímọ́ àti dídúró déédé lórí ẹ̀sìn Ọlọ́hun, dé bi wí pé Ọlọ́hun ṣà wọ́n lẹ́ṣà láti gbé iṣẹ́-ìránṣẹ́ Rẹ̀ àti ẹ̀sìn Rẹ̀ wáá bá àwọn ènìyàn. Gẹ́gẹ́ bí ó ti wá nínú *Al-Qur'ān* pé: **"Wí pé: Ògédé abara bí irú yín ni èmi jẹ́, wọ́n ń ránṣẹ́ sí mi"** (*Al-Kahf:* 110).

Àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun pátápátá, abara ènìyàn ni wọ́n, wọ́n bí wọn gẹ́gẹ́ bí wọ́n ti máa ń bí abara ènìyàn, wọ́n sì kú gẹ́gẹ́ bí wọ́n ti máa ń kú, wọ́n máa ń ṣe àìsàn bíi wọn, wọn kò yàtọ̀ sí wọn níbi bí ara wọn ti rí àti níbi àwọn ohun tí wọ́n bùkáátà sí.

Kò sí nǹkankan nínú lílẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn lára wọn, nítorí pé lílẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn, ti Ọlọ́hun nìkan ṣoṣo ni í ṣe. Ṣùgbọ́n wọ́n jẹ́ abara ènìyàn, wọ́n ránṣẹ́ sí wọn, ìtumọ̀ èyí ni pé; Àṣẹ Ọlọ́hun ń dé ọ̀dọ̀ wọn láti ipasẹ̀ àwọn *Malā'ikah,* tàbí pẹ̀lú àwọn ọ̀nà mìíràn yàtọ̀ sí i.

Àwọn ìjọ ayé ṣe èèmọ̀ nípa iṣẹ́-ìránṣẹ́, nítorí náà Ọlọ́hun kọ ṣíṣe èèmọ̀ wọn, Ó sì ṣàlàyé pé kò sí ohun tó le gbè é lẹ́sẹ̀, nítorí pé èyí gan-an ni ọ̀nà láti mú ìmọ̀nà Ọlọ́hun àti àwọn ẹ̀kọ́ ẹ̀sìn Rẹ̀ dé ọ̀dọ̀ àwọn ẹ̀dá Rẹ̀. **"Ṣé ó jẹ́ ìyanu fún àwọn ènìyàn pé A ránṣẹ́ sí ọkùnrin kan nínú wọn pé: Máa ṣe ìkìlọ̀ fún àwọn ènìyàn, kí o sì fún àwọn ẹni tó gbàgbọ́ lódodo ní ìró ìdùnnú pe ìtìsíwájú dáadáa (ẹ̀san tí ó pé) ń bẹ fún wọn lọ́dọ̀ Ọlọ́hun Ọba wọn? Àwọn aláìgbàgbọ́ wí pé: Dájúdájú eléyìí jẹ́ òpìdán tí ó fojú hàn"** (*Yūnus*: 2).

## Wọ̀ntún-wọ̀nsì nípa ipò Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun:

Ọlọ́hun ṣe àṣàyàn àwọn ẹni ẹ̀ṣà nínú àwọn ẹ̀dá Rẹ̀ láti gbé iṣẹ́-ìránṣẹ́ lọ́wọ́, nítorí náà wọ́n jẹ́ abara ènìyàn tí ó wà ní ipò tí ó ga nínú dídúró déédé lórí ẹ̀sìn Ọlọ́hun àti ṣíṣe dáadáa. Dájúdájú *Al-Qur'ān* ròyìn gbogbo àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun pátápátá pẹ̀lú pé dájúdájú ẹni tí wọ́n ti fi mọ̀nà, olùṣedáadáa, ẹni rere, ẹni tí wọ́n ṣà lẹ́ṣà àti ẹni tí wọ́n gbọ́lá fún lórí gbogbo àgbáyé ni wọ́n. **"84- A sì fi Isḥāq àti Yaʿqūb tọrẹ fún un. Gbogbo wọn ni A fi mọ̀nà, A sì ti fi Nūḥ mọ̀nà síwájú (rẹ), àti pé nínú àwọn arọ́mọdọ́mọ rẹ ni Dāwūd àti Sulaymān àti Ayyūb àti Yūsuf àti Mūsā àti Hārūn. Bayìí ni A sì ṣe máa ń san àwọn olùṣerere lẹ́san. 85- Àti Zakariyyā, àti Yaḥyā, àti ʿĪsā àti Ilyās, gbogbo wọn ni wọ́n wà nínú àwọn ẹni dáadáa. 86- Àti Ismāʿīl àti Ilyasaʿ àti Yūnus àti Lūṭ, àti pé gbogbo wọn ni A gbọ́la fún lórí gbogbo àgbáyé. 87- Àti nínú àwọn bàbáa wọn àti àwọn arọ́mọdọ́mọ wọn àti àwọn arakùnrin wọn, A ṣà wọ́n lẹ̀ṣà, A sì fi wọ́n mọ̀nà lọ sí ọ̀nà tí ó dúró déédé"** (*Al-'An'ām*).

> *Al-Qur'ān*, nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn āyah, kanpá mọ́ ọn pé dájúdájú gbogbo àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun pátápátá, abara ènìyàn ni wọ́n, Ọlọ́hun ṣà wọ́n lẹ́ṣà pẹ̀lú iṣẹ́-ìránṣẹ́ àti ìjẹ́-ìránṣẹ́ Ọlọ́hun.

Tí ẹnìkankan nínú àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun bá ṣe àṣìṣe, Ọlọ́hun kì í fi sílẹ̀ lórí rẹ̀, ṣùgbọ́n yóò pè é sí àkíyèsí nítorí kí ó le ṣẹ́rí padà kúrò níbẹ̀, kí ó sì ronúpìwàdà kúrò níbẹ̀. Ohun tó máa ń ṣe okùnfà èyí ni àṣìṣe níbi ìgbìyànjú, kì í ṣe mímọ̀ọ́mọ̀ kọjá ààlà ohun tí Ọlọ́hun fẹ́ ní ọ̀dọ̀ rẹ̀.

Báyìí ni a ó ṣe rí *Al-Qur'ān* tí ó ń ròyìn àwọn Ànábì ní ìròyìn tí ó múnádóko, tí kò sí àṣejù nínú rẹ̀, tí kò sì sí àṣeètó. Wọ́n jẹ́ ẹni tí wọ́n ṣọ́ kúrò níbi àwọn ẹ̀ṣẹ̀ ńláńlá, síbẹ̀síbẹ̀ abara ènìyàn ni wọ́n, wọn kì í ṣe Ọlọ́hun. Wọn kò sì ní nǹkankan nínú àwọn ohun ẹ̀ṣà *'Ulūhiyyah* àti *Rubūbiyyah* Ọlọ́hun.

Nínú ohun tí yóò fi èyí hàn kedere ni ohun tí Ọlọ́hun mú wá nínú *Al-Qur'ān* nínú ìjomitoro Ọlọ́hun fi bíbọ́pá-bọ́sẹ̀ Ànábì Ọlọ́hun, ʿĪsā – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a – níbi jíjọ́sìn àwọn ènìyàn fún un: ***"Àti pé (rántí) ìgbà tí Ọlọ́hun wí pé: Ìrẹ ʿĪsā ọmọ Maryam! Ṣé ìwọ ni o sọ fún àwọn ènìyàn pé: Ẹ mú èmi àti ìyá mi ni ọlọ́hun méjì yàtọ̀ sí Ọlọ́hun? O wí pé: Mímọ́ fún Ọ. Kò lẹ́tọ̀ọ́ fún mi kí n sọ ohun tí kì í ṣe ẹtọ́ fún mi. Tí ó bá ṣe pe mo sọ ọ́, dájúdájú O ti mọ̀ ọ́n. O mọ ohun tí ó wà ní ẹ̀mí mi, ṣùgbọ́n mi ò mọ ohun tí ó wà ní Ẹmi Rẹ, dájúdájú Ìwọ ni Olùmọ gbogbo ohun tí ó pamọ́ - Mi ò wí nǹkankan fún wọn àyàfi ohun tí O pa mi láṣẹ rẹ̀ pé: Ẹ sin Ọlọ́hun, Ọlọ́hun Ọba mi àti Ọlọ́hun Ọba yín. Mo si jẹ́ ẹlẹ́rìí lé wọn lórí nígbà tí mo wà láàrin wọn, ṣùgbọ́n nígbà tí O gba ẹ̀mí mi. Ìwọ ni O jẹ́ Olùṣọ́ lé wọn lórí, àti pé Ìwọ ni Olùjẹ́rìí lórí gbogbo nǹkan"*** (*Al- Mā'idah*: 116-117).

> Gbogbo ẹni tó bà ka *Al-Qur'ān* yóò mọ̀ pé dájúdájú àwọn *Sūrah* (ọgbà-ọ̀rọ̀) rẹ̀ kan, wọ́n sọ wọ́n lórúkọ pẹ̀lú orúkọ àwọn Ànábì; bíi Ibrāhīm àti Yūsuf, kódà Ọlọ́hun sọ *Sūrah* kan ní orúkọ Maryam, obìnrin mímọ́, ìyá Ànábì ʿĪsā – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –.

## Ipò ẹ̀sìn *Islām* nípa àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun:

Apákan nínú àwọn ènìyàn máa ń lérò pé *Al-Qur'ān* kò jẹ́ nǹkan bíkòṣe àwọn ìtàn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – àti àwọn ìròyìn rẹ̀. Ó máa ń jẹ́ ìyàlẹ́nu fún wọn, nígbà tí wọ́n bá mọ̀ pé, *Al-Qur'ān* dárúkọ Ànábì ʿĪsā – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a – pẹ̀lú pípàtàkì ipò rẹ̀, pẹ̀lú fífọ̀ ọ́ mọ́ kúrò níbi àwọn ẹ̀sùn ìbàjẹ́ tí wọ́n fi kàn án, ní ìgbà 25. Ó sì dárúkọ Ànábì Mūsā – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a – ní ìgbà 136, tí ó sì jẹ́ wí pé kò dárúkọ Ànábì Muḥammad – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a –, ẹni tí ó ṣe wí pé òun ni wọ́n sọ *Al-Qur'ān* kalẹ̀ fún, ju ẹ̀ẹ̀marùn-ún péré lọ.

Nígbà tí ó jẹ́ wí pé àwọn tí ó pọ̀ jùlọ nínú àwọn ẹlẹ́sìn, ní ayé òde-òní, kì í gbà fún ẹlòmíràn yàtọ̀ sí àwọn Ànábì wọn, apákan nínú wọn sì máa ń mú àwọn Ànábì mìíràn ní ọ̀tá, gbogbo ẹni tí ó bá ń ké *Al-Qur'ān,* yóò rí, nínú àwọn āyah tí ó pọ̀, pé dájúdájú ènìyàn kò le jẹ́ Mùsùlùmí, títí tí yóò fi gba gbogbo àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun gbọ́. Àti pé tí ó bá ṣe àigbàgbọ́ pẹ̀lú ẹnikan nínú wọn, tàbí ó ṣe iyèméjì nípa níní àláàfíà ohun tí Ọlọ́hun fi rán an, tàbí ó fi ẹ̀sùn ìbàjẹ́ kàn án, dájúdájú ó ti jáde kúrò nínú ẹ̀sìn *Islām*. Nítorí náà *Al-Qur'ān* kanpá mọ́ ọn pé dájúdájú Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun àti àwọn ẹni tí ó gbà á gbọ́ lódodo, gbàgbọ́ lódodo pẹ̀lú gbogbo ohun tí ó wá láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun. Fún ìdí èyí, wọ́n gbà Ọlọ́hun gbọ́ lódodo, àwọn *Malā'ikah* àti àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, wọn kì í sì ṣe òpinyà, nínú ìgbàgbọ́ wọn, láàrin ẹnìkankan nínú wọn **"Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun gbàgbọ́ lódodo pẹ̀lú ohun tí a sọ̀kalẹ̀ fún un láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun Ọba rẹ̀ àti àwọn olùgbàgbọ́ òdodo. Gbogbo wọn gba Ọlọ́hun gbọ́ lódodo, àti àwọn *Malā'ikah* Rẹ̀, àti àwọn Tírà Rẹ̀ àti àwọn Ìránṣẹ́ Rẹ̀"** (*Al-Baqarah*: 285).



# Ipò ẹ̀sìn *Islām* nípa Ànábì ‘Īsā – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –

Ànábì ‘Īsā – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – jẹ́ ara àwọn ènìyàn tí ó pàtàkì jùlọ láti ìgbà-dégbà, ó sì wà lára àwọn tí ó tóbi jùlọ nínú àwọn ẹni tí ó mu dáadáa wá fún ọmọnìyàn. Àwọn ènìyàn yapa ara wọn níbi ìgbàgbọ́ wọn nípa rẹ̀; láàrin ẹni tí ó kà á sí ọlọ́hun tàbí ọmọ Ọlọ́hun Ọba, àti láàrin ẹni tí ó mú un ní ọ̀tà, tí ó ń fi ẹnu ẹ̀tẹ́ àti àwọn ẹ̀sùn ìbàjẹ́ kàn án. Kí wá ni ìgbàgbọ́ ẹ̀sìn *Islām* nípa Ànábì ‘Īsā – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –?

**1 Ànábì ʻĪsā ń bẹ lára àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun tó pàtàkì jùlọ:**

*Al-Qur'ān* kanpá mọ́ ọn pé dájúdájú Ànábì ʻĪsā – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – jẹ́ ara àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun tí ó tóbi jùlọ, tí ó pàtàkì jùlọ, àti pé dájúdájú ìyà rẹ̀; Maryam, jẹ́ olódodo, olùtẹ̀lé àṣẹ Ọlọ́hun, olùjọsìn fún Ọlọ́hun Ọba rẹ̀, ẹni tí ọwọ́ rẹ̀ mọ́, olùkójúró, wúndíá. Dájúdájú ó ní oyún Ànábì ʻĪsā – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – láìní bàbá, pẹ̀lú agbára Ọlọ́hun, Ọba Abiyì, tí Ó gbọn-n-gbọ́n. Ọlọ́hun dá a pẹ̀lú iṣẹ́-ìyanu tí ó ṣẹ́kù, gẹ́gẹ́ bí Ó ti dá Ādam láìní bàbá àti ìyá, gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́hun ti sọ nínú *Al-Qur'ān* wí pé: Dájúdájú ʻĪsā jẹ́ iṣẹ́-ìyanu gbére, nítorí náà gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́hun ti dá Ādam láìní bàbá àti ìyá, dájúdájú Ó dá ʻĪsā láìní bàbá pẹ̀lú Agbára Rẹ̀, nígbà tí Ó bá sọ fún nǹkan pe: Jẹ́ bẹ́ẹ̀! Tí yóò sì jẹ́ bẹ́ẹ̀. **"Dájúdájú àpèjúwe ʻĪsā lọ́dọ̀ Ọlọ́hun dà gẹ́gẹ́ bíi àpèjúwe Ādam, Ó dá a látara ìyẹ̀pẹ̀, lẹ́yìn náà Ó wí fún un pé: Jẹ́ bẹ́ẹ̀! Ó sì jẹ́ bẹ́ẹ̀"** (*'Āl-'Imrān*: 59).




**2 Mùsùlùmí gba àwọn iṣẹ́-ìyanu tí Ọlọ́hun fún un gbọ́:**

Gẹ́gẹ́ bí Mùsùlùmí ti gbàgbọ́ pẹ̀lú àwọn iṣẹ́-ìyanu, èyí tí Ọlọ́hun jẹ́ kí ó wáyé láti ọwọ́ rẹ̀, bíi; bí ó ti wo adẹ́tẹ̀ àti afọ́jú sàn, jíjí òkú dìde rẹ̀ àti bí ó ti ń sọ ohun tí àwọn èniyàn ń jẹ àti ohun tí wọn ń tọ́jú sí inú ilé wọn, gbogbo èyí pátápátá pẹ̀lú ìyọ̀nda Ọlọ́hun, mímọ́ ni fún Un, Ọba tí ọlá Rẹ̀ ga, ni. Dájúdájú Ọlọ́hun ṣe èyí ní ẹ̀rí tí ó lọ sàn án lórí jíjẹ́-òdodo ìjẹ́-Ànábì rẹ̀ àti ìjẹ́-Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun rẹ̀.

**3 Ọlọ́hun sọ Tírà Rẹ̀ mímọ́, èyí tí í ṣe *'Injīl*, kalẹ̀ fún un:**

*Al-Qur'ān* kanpá mọ́ ọn pé dájúdájú Ọlọ́hun sọ ọ̀kan nínú àwọn Tírà Rẹ̀ tí ó tóbi jùlọ kalẹ̀ fún un – èyí ni *'Injīl* – láti jẹ́ ìmọ̀nà, ìmọ̀lẹ̀ àti ìkẹ́ fún àwọn èniyàn. Àti pé orísìrísì ìyípadà ìtúkútùú ṣẹlẹ̀ sí *'Injīl* láti ìgbà-dégbà.

**4 Abara èniyàn ni, kì í ṣe Ọlọ́hun:**

Ẹ̀sìn *Islām* kàn án nípa pé Ànábì ʻĪsā – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a – jẹ́ abara èniyàn kan nínú àwọn ọmọ Ànábì Ādam. Ọlọ́hun dá a lọ́lá, Ó sì rán an níṣẹ́ sí àwọn ọmọ Isrā'īl, Ó sì jẹ́ kí àwọn iṣẹ́-ìyanu wáyé láti ọwọ́ rẹ̀. Kò ní nǹkankan nínú àwọn ohun ẹ̀ṣà *Rubūbiyyah* àti *'Ulūhiyaah* Ọlọ́hun, gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́hun ti sọ nínú *Al-Qur'ān* wí pé: Īsā kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe ẹrúsìn Ọlọ́hun, tí ó jẹ́ ẹni rere, A ṣe ìdẹ̀ra fún un, A sì fún un ní àwọn iṣẹ́-ìyanu, kí ó le jẹ́ àmí fún àwọn ìjọ rẹ̀ àti ìtọ́ka fún wọn lọ síbi dáadáa **"Òun (ʻĪsā) kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe ẹrúsìn kan ti A ṣe ìdẹ̀ra fún un, àti pé A ṣe é ní àpèjúwe fún àwọn ọmọ *Isrā'īl*"** (*Az-Zukhruf*: 59).

**5 Wọn kò kàn án mọ́ àgbélébùú, ṣúgbọ́n Ọlọ́hun gbé e gùnkè lọ sí sánmà:**

Ànábì ʻĪsā, nínú ìwòyè ẹ̀sìn *Islām*, wọn kò kàn án mọ́ àgbélébùú, ṣúgbọ́n Ọlọ́hun gbé e gùnkè lọ sí sánmà nígbà tí àwọn Yahūd fẹ́ pa á. Ọlọ́hun gbé àfijọ rẹ̀ wọ ẹlòmíràn yàtọ̀ sí i, wọ́n sì pa á, wọ́n sì kàn án mọ́ àgbélébùú, wọ́n rò pé ʻĪsā ọmọ Maryam – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – ni. Gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́hun, Ọba tí ọlá Rẹ̀ ga, ti wí pé: **"Àti nítorí ọ̀rọ̀ wọn pé: Dájúdájú àwa pa *Al-Masīh*; ʻĪsā ọmọ Maryam, Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, wọn kò sì pa á, wọn kò sì kàn án ṣe alóré, ṣùgbọ́n a kàn jẹ́ kí ó rí bẹ́ẹ̀ lójú wọn ni, àti pé dájúdájú àwọn ẹni tí wọ́n ṣe ìyapa ẹnu sí i wà nínú iyèméjì nípa rẹ̀, wọn kò ní ìmọ̀ kankan nípa rẹ̀ àyàfi títẹ̀lé ìméfòó. Wọn kò pa a dájúdájú. Ṣùgbọ́n Ọlọ́hun gbe é gùnkè lọ sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀. Ọlọ́hun si jẹ́ Alágbára, Ọlọ́gbọ́n. Kò sí ẹnìkan nínú àwọn oní-Tírà àyàfi pé ó gbọdọ̀ gbà á gbọ́ síwájú ikú rẹ̀, àti pé ní Ọjọ́ ìgbénde, yóò jẹ́ olùjẹ́rìí lé wọn lórí"** (*An-Nisā'*: 157-158).

## Igi tó ń ṣàlàyé àwọn Ànábì:

Àwọn Ànábì Ọlọ́hun pọ̀, àwọn wọ̀nyí jẹ́ apákan àwọn tí ó gbajúmọ̀ jùlọ nínú wọn – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá wọn –:

**Ādam:**

Bàbá gbogbo abara èniyàn, Ọlọ́hun dá a látara iyẹ̀pẹ̀, Ó sì jẹ́ kí àwọn *Malā'ikah* tẹríba fún un, wọ́n sì sọ̀ ọ́ kalẹ̀ láti ọgbà-ìdẹ̀ra *Al-Jannah* wá sí orí ilẹ̀.

**Nūḥ:**

Ó pe àwọn èniyàn rẹ̀, ṣùgbọ́n wọ́n ṣe àìgbàgbọ́ pẹ̀lú rẹ̀, nítorí náà Ọlọ́hun jẹ wọ́n níyà pẹ̀lú omi *ṭūfān*, òun àti àwọn tó gbà á gbọ́ sì là nínú ọkọ̀ ojú-omi.

**Ibrāhīm:**

Bàbá àwọn Ànábì, ọ̀kan nínú àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun tó pàtàkì jùlọ tó pèpè sí mímọ Ọlọ́hun lọ́kan.

**Ismā'īl:**

Ọmọ Ibrāhīm – kí ọlá Ọlọ́hun máa bá a –, ó ran bàbá rẹ̀ lọ́wọ́ láti kọ́ *Ka'bah*.

**Isḥāq:**

Ọmọ Ibrāhīm – kí ọlá Ọlọ́hun máa bá a –, wọ́n bí i lẹ́yìn tí àwọn *Malā'ikah* fún bàbá rẹ̀ Ibrāhīm ní ìró ìdùnnú pẹ̀lú rẹ̀.

**Ya'qūb:**

Ọmọ Isḥāq – kí ọlá Ọlọ́hun máa bá a –, wọ́n máa ń pè é ní Isrā'īl, àwọn ọmọ *Isrā'īl* máa ń fi ara wọn tì sí ọ̀dọ̀ rẹ̀.

**Yūsuf:**

Ọmọ Ya'qūb – kí ọlá Ọlọ́hun máa bá a –, ojú rẹ̀ rí oníran-ǹ-ran àwọn àdánwó, lẹ́yìn náà ó padà di olórí ìlú ní ìlú Miṣr ní ìgbẹ̀yìn.

**Mūsā:**

Ọ̀kan nínú àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun tó pàtàkì jùlọ, Ọlọ́hun gbé e dìde sí àwọn ọmọ Isrā'īl, Ó sọ Tawrah kalẹ̀ fún un, Ó sì ràn án lọ́wọ́ pẹ̀lú àwọn iṣẹ́-ìyanu, ṣùgbọ́n Fir'awn, ọba ìlú Miṣr pè é ní òpùrọ́, nítorí náà Ọlọ́hun tẹ̀ ẹ́ rì sínú òkun, Ó sì la Mūsā àti àwọn tó wà pẹ̀lú rẹ̀.

**Dāwūd:**

Ànábì tí Ọlọ́hun fún ní ọlá lórí àwọn èniyàn rẹ̀.

**Sulaymān:**

Ọmọ Dāwūd – kí ọlá Ọlọ́hun máa bá a –. Ànábì tí Ọlọ́hun fún ní ọlá tí ó tóbi, Ó sì rọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn ẹ̀dá fún un.

**Zakariyyā:**


Ọ̀kan nínú àwọn Ànábì Ọlọ́hun tó wá nínú àwọn ọmọ *Isrā'īl*, òun ni wọ́n sọ àsọtẹ́lẹ̀ gbígba Maryam, ìyá Ànábì 'Īsā – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá àwọn méjèèjì – tọ́ fún, àti alámójútó títọ́ ọ àti kíkọ́ ọ ní ẹ̀kọ́. Ọlọ́hun fún un ní ọmọkùnrin – orúkọ rẹ̀ ni Yaḥyā – pẹ̀lú pé ó ti dàgbà, tí ìyàwó rẹ̀ sì jẹ́ àgàn.

**'Īsā:**

Ọ̀kan nínú àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun tó pàtàkì jùlọ, Ọlọ́hun dá a látara ìyá, láìní bàbá, Ọlọ́hun sì gbé e dìde sí àwọn ọmọ *Isrā'īl*, Ọlọ́hun sọ '*Injīl* kalẹ̀ fún un, Ó sì ràn án lọ́wọ́ pẹ̀lú àwọn oríṣiríṣi iṣẹ́- ìyanu.

**Muḥammad:**

Ìgbẹ̀yìn àwọn Ànábì, Ọlọ́hun rán an sí gbogbo èniyàn pátápátá, ní ẹni tí ó ń pe àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun tí ó síwájú rẹ̀ ní olódodo, Ó sì sọ *Al-Qur'ān* kalẹ̀ fún un, èyí tí ìbàjẹ́ kò le bá a láti iwájú rẹ̀ tàbí láti ẹ̀yìn rẹ̀.




# Tani Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn *Islām* rán

## Muḥammad

Muḥammad ni orúkọ Ànábì tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn *Islām* rán..

Ó sì jẹ́ ọ̀kan lára àwọn orúkọ tí ó gbajúmọ̀ jùlọ kárí gbogbo àgbáyé ní ayé òde-òní. Ìtumọ̀ rẹ̀ ni; ẹni tí àwọn ènìyàn ń yìn, tí wọ́n sì ń ṣe ẹyìn fún un nítorí àwọn ìwà àti àwọn ìṣe rẹ̀..

Tí ó bá rí bẹ́ẹ̀, ta wáà ni ń jẹ́ Muḥammad?

## Orúkọ Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn *Islām* rán:

Muḥammad ọmọ ‘Abdil-Lāh, ọmọ ‘Abdil-Muṭṭalib ọmọ Hāshim ọmọ ìdílé Quraysh.

Gbogbo àwọn Mùsùlùmí pátápátá ní àdìsọ́kàn pé:

## Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun sí gbogbo àwọn ènìyàn pátápátá:

Ọlọ́hun rán Ànábì wa Muḥammad – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a – sí gbogbo àwọn ènìyàn pátápátá pẹ̀lú gbogbo ìran wọn àti ìpìlẹ̀ wọn. Ó sì ṣe títẹ̀lé e ní ọranyàn lórí gbogbo àwọn ènìyàn. Ọlọ́hun, Ọba tí ọlá Rẹ̀ ga, wí pé: **“Wí pé: Ẹ̀yin ènìyàn! Dájúdájú èmi jẹ́ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun síi yín lápapọ̀”** {*Al-’A‘rāf:* 158}

## Ọlọ́hun sọ *Al-Qur’ān* kalẹ̀ fún un:

Ọlọ́hun sọ̀ Tírà Rẹ̀ tí ó tóbi jùlọ; *Al-Qur’ān*, kalẹ̀ fún Ànábì Muḥammad – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a –, èyí tí ibàjẹ́ kò le bá a láti iwájú rẹ̀ tàbí láti ẹ̀yìn rẹ̀.

## Ìgbẹ̀yìn àwọn Ànábì àti àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun:

Ọlọ́hun rán Ànábì Muḥammad – kí ọlá Ọlọ́hun máa bá a – ní ìgbẹ̀yìn àwọn Ànábì, nítorí náà Ànábì kankan kò ní wá lẹ́yìn rẹ̀, gẹ́gẹ́ bí *Al-Qur’ān* ti wí pé: **“Ṣùgbọ́n ó jẹ́ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun àti ìgbẹ̀yìn àwọn Ànábì”** (*Al-’Aḥzāb*: 40).





## Ìrìn-àjò kíákía láti mọ̀ nípa Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn *Islām* rán, Muḥammad – kí ọlá Ọlọ́hun máa bá a –:

**1. Bíbí rẹ̀:**

A bí i ní ìlú *Makkah*; ìwọ̀-òòrùn erékùsù ilẹ̀ Lárúbáwá, ní ọdún 570 lẹ́yìn bíbí Ànábí ‘Isā, ní ẹni tí kò ní bàbá. Ó tún pàdánù iyá rẹ̀ ní ìgbà èwe. Nítorí náà ní abẹ́ àmójútó bàbáa-bàbá rẹ̀ ‘Abdul-Muṭṭalib ni ó ti gba ìtọ́jú. Lẹ́yìn náà ní abẹ́ àmójútó arákùnrin bàbá rẹ̀ Abū Ṭālib, ẹni tí ó ṣọ́ ọ, tí ó sì kọdí àwọn ọ̀tá rẹ̀.

**2. Ìṣẹ̀mí àti ìdàgbàsókè rẹ̀:**

Ó ṣẹ̀mí nínú ìdílé *Quraysh* fún ogóji ọdún kí Ọlọ́hun tó gbé e dìde ní Òjíṣẹ́ (570-610 lẹ́yìn bíbí Ànábí ‘Isā). Ní ìgbà yìí, ó jẹ́ àpẹẹrẹ rere fún ìwà dáadáa àti àpèjúwe rere níbi dídúró sinsin àti dídáyàtọ̀. Àlàjẹ́ rẹ̀ tí ó gbajúmọ̀ láàrin wọn ní ìgbà náà ni: Olódodo, ẹni tí ó ṣe fi ọkàn tán. Ó máa ń ṣiṣẹ́ darandaran, lẹ́yìn náà ó ṣe kárà-kátà.

Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, síwájú kí ẹ̀sìn *Islām* tó dé, jẹ́ ẹni tí ó ṣẹ́rí kúrò níbi ẹbọ. Ó máa ń sin Ọlọ́hun ní ìlànà ijọsin Ànábí Ibrāhīm, ó sì máa ń kọ jíjọ́sin fún òrìṣà àti gbogbo ìṣesí àwọn olóòṣà, tí ó sì jẹ́ wí pé òpè ni, ní ìgbà náà, kò mọ̀ ọ́n kọ, kò mọ̀ ọ́n kà.

**3. Gbígbé e dìde ní Òjíṣẹ́:**

Lẹ́yìn tí Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – ti lo ogóji ọdún pé nínú ọjọ́ orí rẹ̀, tí ó ń ronú, tí ó sì ń jọ́sin fún Ọlọ́hun nínú kòtò *Ḥirā*’, ní òkè An-Nūr, iṣẹ́-ìránṣẹ́ wá bá a láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun, *Al-Qur’ān* sì bẹ̀rẹ̀ sí máa sọ̀kalẹ̀ fún un. Àkọ́kọ́ ohun tí ó sọ̀kalẹ̀ fún un nínú *Al-Qur’ā*n ni ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun pé: Ké, ní ẹni tí ó ń wá ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú Orúkọ Ọlọ́hun Ọba rẹ, Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá rẹ. **“Ké! Pẹ̀lú Orúkọ Ọlọ́hun Ọba rẹ, Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá (gbogbo ẹ̀dá)”** (*Al-‘Alaq*: 1). Kí ó le polongo pé ìgbédìde yìí, láti ìbẹ̀rẹ̀ rẹ̀, jẹ́ ìgbà ọ̀tun nínú ìmọ̀, kíkà nǹkan, ìmọ̀lẹ̀ àti ìmọ̀nà fún àwọn èniyàn. Lẹ́yìn náà ṣísọ̀kalẹ̀ *Al-Qur’ān* fún un tẹ̀ síwájú fún ọdún mẹ́talélógún.




**4. Ìbẹ̀rẹ̀ pípèpè rẹ̀:**

Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun bẹ̀rẹ̀ pípèpè sí ẹ̀sìn Ọlọ́hun ní bòńkẹ́lẹ́ fún ọdún mẹ́ta. Lẹ́yìn náà, ó ṣe àfihàn ìpèpè rẹ̀, ó sì polongo rẹ̀ síta fún ọdún mẹ́wàá mìíràn. Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun àti àwọn sàábé rẹ̀, nígbà yìí, bá oníranǹran ìninilára tí ó le koko jùlọ àti àbòsí pàdé ní ọ̀dọ̀ ìdílé rẹ̀, tí í ṣe *Quraysh*. Ó ṣẹ́rí ẹ̀sìn *Islām* sí àwọn ìdílé tí ó wá ṣe àbẹ̀wò ilé Ọlọ́hun (*Ḥajj*), àwọn ara ìlú Madīnah sì tẹ́wọ́ gbà á. Nítorí náà ṣíṣe ìrìn-àjò àwọn Mùsùlùmí lọ síbẹ̀ bẹ̀rẹ̀ díẹ̀ díẹ̀.

**5. Fífi ìlú *Makkah* sílẹ̀ rẹ̀:**

Ó fi ìlú *Makkah* sílẹ̀ lọ sí ìlú *Madīnah* oní-ìmọ́lẹ̀, èyí tí à ń pè ní Yathrib nígbà náà, ní ọdún (622 lẹ́yìn bíbí Ànábí ʻIsā). Ó sì wà ní ọmọ ọdún mẹ́tàléláàdọ́ta nígbà náà, lẹ́yìn tí àwọn abẹnugan ìdílé Quraysh, nínú àwọn tí ó tako pípèpè rẹ̀, tí wọ́n sì gbiyànjú láti pa á, ti pa ìmọ̀ràn papọ̀ lé e lórí. Ó gbé ibẹ̀ fún ọdún mẹ́wàá ní ẹni tí ó ń pèpè lọ sínú ẹ̀sìn *Islām*, ó sì pàṣẹ ìrun kíkí àti *Zakāh* yíyọ àti àwọn ìlànà ìjọsìn ẹ̀sìn Islām tí ó kù.






**6. Bí ó ti tan ẹ̀sìn *Islām* ká:**

Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun fi ìpìlẹ̀ ọ̀làjú ẹ̀sìn *Islām* lélẹ̀ ní ìlú *Madīnah* lẹ́yìn tí ó ti fi ìlú *Makkah* sílẹ̀ (622-632 lẹ́yìn bíbí Ànábí ʻIsā). Ó tún fi àwọn àmí àwùjọ Mùsùlùmí rinlẹ̀. Ó sì pa títara fún ìdílé rẹ́. Ó fọ́n ìmọ̀ ká. Ó fi àwọn ìpìlẹ̀ déédé, dídúró sinsin, ìjẹ́-ọmọ-ìyá, ríran ara ẹni lọ́wọ́ àti ètò rinlẹ̀. Àwọn ìdílé kan gbiyànjú láti ká ẹ̀sìn *Islām* lápá kò, nítorí náà àwọn ogun àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ kan wáyé. Ọlọ́hun sì ran ẹ̀sìn Rẹ̀ àti Ìránṣẹ́ Rẹ̀ lọ́wọ́. Lẹ́yìn náà àwọn èniyàn wọnú ẹ̀sìn *Islām* kẹ̀tíkẹ̀tí. Ìlú Makkah, ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ìlú, àti àwọn ìdílé ní erékùsù ilẹ̀ Lárúbáwá fìnnúfíndọ̀ wọnú ẹ̀sìn *Islām*, ní ẹni tí ẹ̀sìn tí ó tóbi yìí tẹ́ ní ọrùn.

**7. Ikú rẹ̀:**


Nínú oṣù Ṣafar (oṣù kejì ojú-ọ̀run) ọdún 11, lẹ́yìn fífi ìlú *Makkah* sílẹ̀ Ànábì lọ sí ìlú *Madīnah* àti lẹ́yìn tí Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun ti mú iṣẹ́ Ọlọ́hun dé ògóńgó, tí ó sì ti pé ohun tí Ọlọ́hun gbé kọ́ ọ lọ́rùn, tí Ọlọ́hun sì ti pé ìdẹ̀ra Rẹ̀ lórí àwọn èniyàn pẹ̀lú pípé ẹ̀sìn *Islām*, àìsàn ibà ṣe Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –, àìsàn yìí pada lágbára lára rẹ̀. Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – sì kú ní ọ̀sán ọjọ́ ajé, *Rabīʻul-ʼAwwal* (oṣù kẹta ojú-ọ̀run) ní ọdún 11, lẹ́yìn *Hijrah*, ó ṣe déédé (8/6/632 lẹ́yìn bíbí Ànábí ʻIsā). Ó sì lo ọdún mẹ́tàlélọ́gọ́ta láyé, wọ́n sì sin ín sí yàrá ʻĀʼishah ní ẹ̀gbẹ́ Mọ́ṣálásí Ànábì.





# Muḥammad, jẹ́ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, nínú ìwòye àwọn onídéédé

Ẹni tó bá jẹ́ onídéédé – irú ọ̀làjú tí ó wulẹ̀ kó ní – kò le ní ìkápá nǹkankan, nígbà tó bá ka ìtàn Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – àyàfi kí ó jẹ ìyàlẹ́nu fún un, kí ó sì ṣe èǹmọ̀ pẹ̀lú gbogbo àlàyé ìtan  gbére yìí. A ó rí àwọn onímímọ̀ àti àwọn amòye àti àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n, láti ibùyọ àti ibùwọ̀ òòrùn, tí wọ́n ń jẹ́rìí sí èyí, tí wọ́n sì ń kọ ọ́ sílẹ̀ nínú ìwé wọn àti ìbánisọ̀rọ̀ wọn. Nínú èyí ni:



**Ghāndi, nínú ìwé rẹ̀; (“Young India”,1924) sọ wí pé:**

Mo fẹ́ mọ àwọn ìròyìn ọkùnrin, èyí tí ó ń darí ọkàn ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ mílíọ̀nù àwọn ènìyàn.. Mó ti gbàgbọ́ tán pátápátá pé dájúdájú kì í ṣe idà ní àtẹ̀gùn, èyí tí ẹ̀sìn Islām ti ipasẹ̀ rẹ̀ dé ipò tí ó wà. Ṣùgbọ́n èyí wáyé látara ìwà pẹ̀lẹ́ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, níní àwòjinlẹ̀ rẹ̀ àti òdodo rẹ̀ níbi àdéhùn, àti níní àkàkún àti àfọ̀mọ́ ọkàn fún àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ àti àwọn ọmọlẹ́yìn rẹ̀, àti jíjẹ́ akin rẹ̀ pẹ̀lú níní àfọkàntán pátápátá sí Ọlọ́hun Ọba rẹ̀ àti sí iṣẹ́ tí wọ́n fi rán an. Àwọn ìròyìn wọ̀nyí ló la ọ̀nà, tó sì sọ àwọn ohun tó le di ìrọ̀rùn, kì í ṣe pẹ̀lú idà. Lẹ́yìn tí mo ka ìpín kejì nínú ìṣẹ̀mí-ayé Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun tán, mo rí i pé inú mi bàjẹ́, nítorí pé kò sí àlékún láti mọ̀ jù bẹ́ẹ̀ lọ nípa ìṣẹ̀mí-ayé rẹ̀ tó pàtàkì.

*Mahatma Gandhi*, ọ̀rọ̀ tí wọ́n tẹ̀ jáde i “*Young India*/ 11”,1924/9

**“Mo fẹ́ mọ àwọn ìròyìn ọkùnrin, èyí tí ó ń darí ọkàn ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ mílíọ̀nù àwọn ènìyàn.. Mó ti gbàgbọ́ tán pátápátá pé dájúdájú kì í ṣe idà ní àtẹ̀gùn, èyí tí ẹ̀sìn Islām ti ipasẹ̀ rẹ̀ dé ipò tí ó wà” Gandhi**




Nínú ìwé rẹ̀ tó gbajúmọ̀ (Àwọn ọgọ́rùn-ún ọkùnrin tó pàtàkì jùlọ nínú ìtàn-ayé), **Michael H. Hart** bẹ̀rẹ̀:

Àwọn ọgọ́rùn-ún ènìyàn pàtàkì yìí pẹ̀lú Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –. Ó ṣàlàyé ìdí tí òun fi ṣà á lẹ́ṣà, pẹ̀lú ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé: (Dájúdájú ṣíṣa Muḥammad lẹ́ṣà mi, láti jẹ́ àkọ́kọ́ nínú àwọn tó pàtàkì jùlọ, tó sì tóbi jùlọ nínú àwọn ènìyàn ìtàn-ayé yìí, níti pàápàá, le ya àwọn òǹkàwé lẹ́nu, ṣùgbọ́n òun ni ọkùnrin kan ṣoṣo nínú gbogbo ìtàn-ayé yìí pátápátá, èyí tí yíyege rẹ̀ ga jùlọ ní ọ̀nà méjèèjì: ti ẹ̀sìn àti ilé-ayé).

*Michael Hart in ‘The 100, A Ranking of the Most Influential Persons In History,’ p.33*






Gbajúmọ̀ akọrin, ara ìlú Faransé (France); **Alphonse de Lamartine**, nínú ìwé rẹ̀ “ìtàn ìlú Turkiyā (Turkey)”, sọ wí pé: Dájúdájú gíga ẹ̀ròńgbà, lílẹ̀ àwọn irinṣẹ́ àti àṣeyọrí ńlá, èyí ni àmí mẹ́tẹ̀ẹ̀ta fún jíjẹ́ akin ènìyàn. Tani ó wá le ṣe àyà gbàǹgbà láti fi (Ànábì) Muḥammad wé ẹnikankan nínú àwọn ènìyàn pàtàkì inú igbà?

Nínú ìwé rẹ̀: *Histoire de la Turquie*, ìdì 1, ojú-ewé 111.



Ọ̀jọ̀gbọ́n, ará ìlú Índíà; **Ramakrishna** sọ wí pé: (Àwọn ìgbà ń yípadà, ṣùgbọ́n (Ànábì) Muḥammad kò yípadà, bóyá nígbà tí ó bá borí tàbí wọ́n ṣẹ́gun rẹ̀, nígbà tí agbára wà lọ́wọ́ rẹ̀ tàbí nígbà ìlekoko, nígbà ọrọ̀ tàbí ìpọ́njú. Ènìyàn kan náà ni, àwọn ìròyìn rẹ̀ wọ̀nyí kò yí padà, gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ wí pé èyí ni Èròńgbà Ọlọ́hun fún gbogbo àwọn Ànábì, èyí tí kò le yípadà láéláé).

*Nínú ìwé rẹ̀: Muhammad The Prophet of Islam*, ojú-ewé 24.



Akọrin tí ó tóbi jùlọ ní ìlú Almāniyā (Germany); **Goethe,** sọ nípa ara rẹ̀, nínú ìwé tí ó fi ṣọwọ́ sí olólùfẹ́ rẹ̀ lóbìnrin, nígbà tí ó ń ṣàlàyé bí ẹ̀sìn Islām àti Ànábì Muḥammad tí jọ ọ́ lójú tó, wí pé: (Dájúdájú bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé òun ti pé ọmọ àádọ́rin ọdún, ìfàsẹ́yìn kò bá jíjọ òun lójú ẹ̀sìn Islām láéláé, ṣùgbọ́n ó ń tóbi sí i, fífi ẹsẹ̀ rinlẹ̀ rẹ̀ sì tún ń gbópọn sí i).

*Katharina Mommsen sọ èyí, nínú ìwé rẹ̀, nípa Goethe: Goethe und die arabische Welt,* ojú-ewé 177.

Àgbà ọ̀jẹ̀ onímímọ̀, **Stobart,** sọ wí pé:

(Kò sí ẹnikankan, nínú ìtàn ọmọnìyàn láti òkè délẹ̀, tí ó súnmọ́ irú ẹ̀dá tí (Ànábì) Muḥammad jẹ́ .. pẹ̀lú bí àwọn irinṣẹ́ tí ó ní lọ́wọ́ ti kéré tó, ohun tí ó mú wá nínú ìjẹ́-akin tó wọ́n, tóbi jọjọ. Tí a bá ṣe àgbéyẹ̀wò ìtàn ní abala yìí, a kò le rí orúkọ kankan tí ìmọ́lẹ̀ rẹ̀ tàn, tí ó sì hàn kedere yàtọ̀ sí orúkọ Ànábì (Muḥammad), tí ó jẹ́ ọmọ ìran Lárúbáwá).

*Nínú ìwé rẹ̀: Islam and Its Founder,* ojú-ewé 227-228.



**Simon Ockley,** nínú ìwé rẹ̀ nípa ìtàn àsìkò ìjọba àwọn Mùsùlùmí, wí pé:

(Kì í ṣe gbígbilẹ̀ ìpèpè ẹ̀sìn *Islām* ni ó yẹ kí ó ya ènìyàn lẹ́nu, ṣùgbọ́n títẹ̀ síwájú rẹ̀ àti fífi ẹsẹ̀ rinlẹ̀ rẹ̀ láti ìgbà-dégbà, irú ìwúrí tí ó jọ ènìyàn lójú, èyí tí (Ànábì) Muḥammad ti gbé sílẹ̀ ní ìlú Makkah àti Madīnah, kò yẹ kúrò lórí ẹwà àti agbára yìí kan náà nínú ẹ̀mí àra ìlú *India, Africa àti Turkey*, àwọn ẹni tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ mọ *Al-Qur'ān*).

*Nínú ìwé rẹ̀: History of the Saracen Empire,* ojú-ewé 45.

**Irú ìwúrí tí ó jọ ènìyàn lójú, èyí tí (Ànábì) Muḥammad ti gbé sílẹ̀ ní ìlú Makkah àti Madīnah, kò yẹ kúrò lórí ẹwà àti agbára yìí kan náà nínú ẹ̀mí àwọn àra ìlú *India, Africa àti Turkey,* àwọn ẹni tí ó ṣẹ̀ṣẹ̀ mọ *Al-Qur'ān*). Simon Ockley**



**Will Durant** nínú ìwé rẹ̀ tí ó gbajúmọ̀; *Qiṣṣatul-Ḥaḍāra,* wí pé:

"Tí a bá fi bí lílapa ẹni tí ó pàtàkì ti tó, lára àwọn ènìyàn, dájọ́ lórí pípàtàkì rẹ̀, a ó sọ pé: Dájúdájú Ànábì Muḥammad wà lára àwọn ẹni tí ó tóbi jùlọ nínú ìtàn ayé. Ó kà á sí ojúṣe fún ara rẹ̀, pé òun yóò mú ìdàgbàsókè bá ipò ẹ̀mí àti ìhùwàsí, fún àwọn ìran ènìyàn tí òkùnkùn ìwàkíwà ti bò dáru, àti ojú-ọjọ́ àti ọ̀dá ilẹ̀ òkóò. Dájúdájú ó yege níbi mímú èròngbà rẹ̀ ṣẹ, ní yíyege tí alátúnṣe mìíràn kankan kò súnmọ́ ọn níbẹ̀ nínú gbogbo ìtàn-ayé pátá. Ó kéré kí á rí ènìyàn kan, yàtọ̀ sí i, tí ọwọ́ rẹ̀ tẹ gbogbo ohun tó jẹ́ àfojúsùn rẹ̀. Àwọn ìlú Lárúbáwá, nígbà tó bẹ̀rẹ̀ ìpèpè rẹ̀ jẹ́ ilẹ̀ pápá tí kò ní omi, àwọn ìdílé tó jẹ́ abọ̀rìṣà ní ó ń gbé ibẹ̀, òǹkà wọn kéré, ẹnu wọn kò sì kò, ṣùgbọ́n nígbà tó kú, ó ti di ìjọ kan ṣoṣo tó so mọ́ ara wọn. Ó fi òpin sí ìgbónára ẹléyàmẹ̀yà àti àwọn àgbélẹ̀rọ ìgbàgbọ́, ó sì fi rinlẹ̀ lórí ẹ̀sìn Yahūdiyyah, ẹ̀sìn Masīḥīyyah àti ẹ̀sìn ìlú rẹ̀ àtijọ́; ẹ̀sìn mìíràn tó fojú hàn kedere, tó sì lágbára, àti ìhùwàsí tó ṣe ojú lọ́yìn, èyí tó dúró lórí jíjẹ́ akin àti iyì àwùjọ. Nínú ìran kan ṣoṣo, ó borí níbi ọgọ́rùn-ún ogun, ó sí rí orílẹ̀ èdè tó tóbi dá sílẹ̀ láàrin ọdúnrún kan ṣoṣo, ó rí i ṣe pé kí ó ṣẹ́kù, títí di ayé òde-òní, gẹ́gẹ́ bíi agbára kan tó ní ipa tó tóbi lára ìlàjì gbogbo àgbáyé".

**"Tí a bá fi bí lílapa ẹni tí ó pàtàkì ti tó, lára àwọn ènìyàn, dájọ́ lórí pípàtàkì rẹ̀, a ó sọ pé: Dájúdájú Ànábì Muḥammad wà lára àwọn ẹni tí ó tóbi jùlọ nínú ìtàn ayé" Will Durant**

*Will Durant, In The Story of Civilization* 13 / 47

Ọ̀kan nínú àwọn ọ̀tá Muḥammad tó le koko jùlọ, lẹ́yìn ìgbà tó gba ẹ̀sìn Islām tán, rọ́ ìtàn kan tó yani lẹ́nu fún wa. Èyí ni ìgbà tí lẹ́tà Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – dé ọ̀dọ̀ *Hiraql*, ọba àgbà ní ilẹ̀ Rūm, ní ọdún (628 lẹ́yìn bíbí Ànábì 'Īsā), tí ó ń pè é sí ẹ̀sìn *Islām* nínú rẹ̀, èyí ya *Hiraql* lẹ́nu, ó bèrè fún pé kí wọ́n mú ẹnikan wá láti ilẹ̀ Lárúbáwá, èyí tó mọ̀, tó sì tan mọ́ ẹni tó fi ìwé ránṣẹ́. Abū Sufyān, ní ìgbà náà, wà lórí ìrìn-àjò òwò rẹ̀ ní ìlú *Shām* (ó sì jẹ́ ara àwọn asiwájú ìran *Quraysh*, tí bíbá Ànábì ṣe ọ̀tá rẹ̀ le koko jùlọ ní ìgbà náà), nítorí náà wọ́n pè é àti àwọn tó wà pẹ̀lú rẹ̀ wá sí ààfin. *Hiraql*, láti ipasẹ̀ òǹgbùfọ̀ rẹ̀, bi wọ́n léèrè àwọn ìbéèrè tó dé ògóngó níbi orí pípé àti ọgbọ́n; nítorí kò le mọ òdodo Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – yàtọ̀ sí irọ́ rẹ̀. Ṣùgbọ́n nígbà tó gbọ́ àwọn èsì Abū Sufyān sí àwọn ìbéèrè rẹ̀, *Hiraql*, ní ẹni tó dojú ọ̀rọ̀ kọ Abū Sufyān, sọ wí pé:

Mo bi ẹ́ léèrè nípa ẹbí rẹ̀, o sì dáhùn pé dájúdájú ó jẹ́ ẹlẹ́bí pàtàkì láàrin yín, báyìí ni àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, wọ́n máa ń gbé wọn dìde nínú ẹbí pàtàkì nínú ìran wọn. Mo tún bi ẹ́ léèrè pé ṣe ẹnikan nínú yín ti sọ irú ọ̀rọ̀ yìí rí? O sì dáhùn pé bẹ́ẹ̀ kọ́, nítorí náà mo sọ wí pé: Tí ó bá ṣe ẹnikan ti síwájú rẹ̀ sọ bẹ́ẹ̀ ni, mi ò bá sọ wí pé: Ẹni tó ń fi ara wé ẹni tó ṣe síwájú rẹ̀ ni.

Mo tún bi ẹ́ pé; ṣé ẹ ti máa ń fi ẹ̀sùn irọ́ pípa kàn án tẹ́lẹ̀ síwájú kí ó tó sọ ohun tó sọ? O sì dáhùn pé bẹ́ẹ̀ kọ́. Ìyẹn jẹ́ kí n mọ̀ pé dájúdájú kò le fi pípa irọ́ mọ́ àwọn ènìyàn sílẹ̀, lẹ́yìn náà kí ó wá máa parọ́ mọ́ Ọlọ́hun.

Mo bi ẹ́ pé; ṣé àwọn ènìyàn pàtàkì ni wọ́n ń tẹ̀lé e, àbí àwọn ẹni yẹpẹrẹ? O sì dáhùn pé; àwọn ẹni yẹpẹrẹ ni ń tẹ̀lé e, àwọn náà sì ni ọmọlẹ́yìn àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun. Mo tún bi ẹ́ pé; ṣé wọ́n ń lékún sí i ni àbí wọ́n ń dínkù? O sì dáhùn pé; wọ́n ń lékún sí i ni. Báyìí náà sì ni ọ̀ràn ìgbàgbọ́ òdodo títí tí yóò fi pé.

Mo bi ẹ́ pé; ṣé ẹnìkankan kómọ̀ kúrò lẹ́yìn rẹ̀ látara ìkórìíra sí ẹ̀sìn rẹ̀ lẹ́yìn tó ti wọnú rẹ̀ tẹ̀lẹ́, o sì dáhùn pé bẹ́ẹ̀ kọ́. Báyìí náà sì ni ọ̀ràn ìgbàgbọ́ òdodo rí nígbà tó bá ti rọ̀pọ̀ mọ́ àwọn ọkàn.

Mo tún bi ẹ́ pé; ṣé ó máa ń jàǹbá? O sì dáhùn pé bẹ́ẹ̀ kọ́. Báyìí náà sì ni àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, wọn kì í jàǹbá.

Mo tún bi ẹ́ pé; kín ni ó ń pa yín láṣẹ rẹ̀? O sì dáhùn pé ó ń pa yín láṣẹ kí ẹ máa jọ́sìn fún Ọlọ́hun, ẹ kò sì gbọdọ̀ fi nǹkankan ṣẹbọ pẹ̀lú Rẹ̀, ó sì ń kọ̀ fún yín nípa jíjọ́sìn fún àwọn òrìṣà, ó sì ń pa yín láṣẹ ìrun kíkí, òdodo sísọ àti níní àmójúnù.


Tí ó bá jẹ́ wí pé òdodo ni ohun tí ò ń sọ, yóò padá ní ìkápá lórí ààyè gìgísẹ̀ mi méjèèjì yìí. Dájúdájú mo ti mọ̀ pé yóò jáde, ṣùgbọ́n mi ó lérò pé ààrí yín ni yóò ti wá. "Tí ó bá jẹ́ wí pé mo le dé ọ̀dọ̀ rẹ̀ ni, dájúdájú mí ò bá gbiyànjú láti lọ pàdé rẹ̀" (*Al-Bukhārī*: 7).



# Díẹ̀ nínú ìtàn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, Muḥammad, àti àwọn ìwà rẹ̀

Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a – jẹ́ àpèjúwe fún àwọn ìwà ìjọ́mọnìyàn tí ó ga jùlọ. Gbogbo onídéédé, ní ibùyọ̀ àti ìbùwọ̀ oòrùn jẹ́rìí sí èyí àti àwọn ọ̀tá rẹ̀ bákan náà, títí tí ó fi jẹ́ wí pé, ó tọ́ sí kí *Al-Qur'ān* ròyìn ìwà rẹ̀ pẹ̀lú títóbi..

Nígbà tí wọ́n bi ìyàwó rẹ̀; ‘Ā’ishah – kí Ọlọ́hun yọ́nú sí i – léèrè nípa ìwà Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, Muḥammad, kò rí ìròyìn kankan tí ó ṣe régí láti fi ṣàlàyé ìwà rẹ̀, ju ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé: “*Al-Qur’ān* ni ìwà rẹ̀” lọ. Èyí túmọ̀ sí pé: Ó jẹ́ àpẹ̀júwe fún ṣíṣe àmúlò àwọn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ *Al-Qur’ān* àti àwọn ìwà rẹ̀.



**Èyí ni àlàyé ránpẹ́ nípa ìtàn rẹ̀ àti àwọn ìwà rẹ̀:**

## Ìtẹ́ríba:

Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – kì í yọ́nú sí kí ẹnikankan dìde fún un láti fi gbé e tóbi, ṣúgbọ́n ó máa ń kọ̀ fún àwọn sàábé rẹ̀ nípa ṣíṣe èyí, títí tí ó fi jẹ́ wí pé àwọn sàábé, pẹ̀lú bí ìfẹ́ wọn sí i ti lágbára tó, wọn kì í dìde fún un nígbà tí wọ́n bá rí pé ó ń bọ̀. Èyí kò déédé rí bẹ́ẹ̀ bíkòṣe nítorí pé wọ́n mọ̀ pé ó kòríira rẹ̀. (*Aḥmad*: 12345).

‘Adiyy ọmọ Ḥatim – kí Ọlọ́hun yọ́nú sí i – wá bá a, síwájú kí ó tó gbà ẹ̀sìn Islām, ó sì jẹ́ ara àwọn ènìyàn pàtàkì nínú ìran Lárúbáwá, ó fẹ́ mọ̀ nípa pàápàá ìpèpè rẹ̀, ‘Adiyy wí pé: “Mo wá bá a, ní mo bá rí i pé òbìnrin kan àti ọmọdé méjì tàbí ọmọdé kan wà ní ọ̀dọ̀ rẹ̀ – ó sọ̀rọ̀ nípa bí wọ́n ti súnmọ́ Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – tó, nítorí náà mo mọ̀ pé kì í ṣe ọba Kisrā, kì í sì ṣe *Qayṣar*” (*Aḥmad*: 19381). Nítorí náà ìtẹ́ríba jẹ́ ìwà gbogbo àwọn Ànábí pátá.

Ó máa ń jókòó pẹ̀lú àwọn sàábé rẹ̀, bíi ọ̀kan lára wọn, kì í jókòó sí ibùjokòó tí yóò ṣàdáyanrí rẹ̀ yàtọ̀ sí àwọn tí ó wà ní ẹ̀gbẹ̀ẹ̀gbẹ́ rẹ̀, títí tí ó fi jẹ́ wí pé àlejò tí kò mọ̀ ọ́n tẹ́lẹ̀, tí ó bá wọ ààyè ibi tó wà, kò le ṣe ìyàtọ̀ láàrin rẹ̀ àti àwọn sàábé rẹ̀. Nítorí náà àwọn ènìyàn máa ń bèèrè pé: Tani Muḥammad nínú yín? (*Al-Bukhārī:* 63).

Apákan nínú àwọn sàábé rẹ̀ fún wa ní ìró nípa rẹ̀ pé dájúdájú pẹ̀lú àìráàyè rẹ̀, kì í kọ̀ láti jáde láti gbọ́ bùkáátà àwọn ènìyàn àti àwọn ohun tó jẹ́ àǹfààní fún wọn bí ó ti wulẹ̀ kó kéré tó. Ní ìgbà mìíràn, ọ̀kan nínú àwọn ẹrúbìnrin àwọn ará ìlú *Madīnah* máa ń gbá Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – lọ́wọ́ mú, tí yóò sì máa fà á lọ síbi tí ó bá fẹ́ láti lọ bá a gbọ́ bùkáátà rẹ̀. (*Al-Bukhārī:* 5724).

Sàábé pàtàkì, ‘Umar ọmọ Al-Khaṭṭāb, fún wa ní ìró nípa bí ó ti wọlé ti Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, Muḥammad, ní ọjọ́ kan, ó sì rí orípa ẹní (ìtẹ́ tí wọ́n hun látara imọ̀ ọ̀pẹ dàbínù) ní ẹ̀gbẹ́ rẹ̀, ó sì bú sẹ́kún. Nítorí náà ó wí pé: “Kín ni ó pa ẹ́ lẹ́kún?” ‘Umar dáhùn pé: Ìrẹ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun! Dájúdájú *Kisrā* àti *Qayṣar* ń bẹ nínú ohun tí àwọn méjèèjì wà nínú rẹ̀ (nínú ìdẹ̀ra), ìwọ sì jẹ́ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun! Nítorí náà ó wí pé: “Ṣé kò dùn mọ́ ọ kó jẹ́ ti wọn láyé, kí ó sì jẹ́ ti wa lọ́run”. (*Al-Bukhārī:* 3503).

> Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn Islām rán máa ń ṣe àtúnṣe àwọn ohun-ìní rẹ̀ fún ara rẹ̀, ó máa ń ran àwọn ará-ilé rẹ̀ lọ́wọ́, ó sí máa ń bá wọn kópa níbi àwọn iṣẹ́ ilé.



Ó máa ń ṣe àtúnṣe àwọn ohun-ìní rẹ̀ fún ara rẹ̀, ó máa ń ran àwọn ará-ilé rẹ̀ lọ́wọ́, ó sí máa ń bá wọn kópa níbi àwọn iṣẹ́ ilé. Nígbà tí wọ́n bi ìyàwó rẹ̀; ‘Ā’ishah – kí Ọlọ́hun yọ́nú sí i – léèrè nípa iṣesí rẹ̀ nínú ilé rẹ̀, ó dáhùn pé: “Ó máa ń wà níbi iṣẹ́ àwọn ara ilé rẹ̀” (*Al-Bukhārī*: 5048). Ohun tó gbà lérò ni pé ó máa ń ràn àwọn ara ilé rẹ̀ lọ́wọ́. Ó tún wí pé: “Gẹ́gẹ́ bí ẹnìkọ̀ọ̀kan nínú yín ti máa ń ṣe: Ó máa ń so bàtà ara rẹ̀, ó sì máa ń rán aṣọ rẹ̀ tó ya fún ara rẹ̀”. (*Aḥmad*: 24749).

Ànábí – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wí pé: “Ẹnikẹ́ni tí ìwọ̀n ọmọ-ináagún kan nínú motómotó bá wà ní ọkan rẹ̀ kò ní wọ ọgbà-ìdẹ̀ra *Al-Jannah*” (*Muslim*: 91)

## Àánú:

Dájúdájú Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wí pé: “Àwọn aláánú, Ọlọ́hun, Ọba Àjọkẹ́ Ayé yóò ṣe ààǹú fún wọn. Nítorí náà ẹ máa ṣe ààǹú fún àwọn tí ń bẹ lórí ilẹ̀, Ẹni tí ń bẹ ní sánmà yóò ṣe ààǹú fún yín” (*Abu Dāwūd*: 4941)

**Àánú Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – yóò hàn ní oríṣiríṣi ọ̀nà, nínú rẹ̀ ni:**

### Níní ààǹú rẹ̀ pẹ̀lú àwọn ọmọwẹẹrẹ:

- Pẹ̀lú bí ó ti jẹ́ wí pé dájúdájú ìrun ni òpó tí ẹ̀sìn Islām dúró lé lórí, èyí tí ọ̀rọ̀ sísọ kò ní ẹ̀tọ́ nínú rẹ̀, tàbí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àìfarabalẹ̀. Dájúdájú Ànábí – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a – kírun ní ọjọ́ kan, tí ó sì gbé ọmọ-ọmọ rẹ̀ obìnrin; ’Umāmah, ọmọbìnrin Zaynab lọ́wọ́, nígà tí ó bá fi orí kanlẹ̀, yóò gbé e kalẹ̀. Nígbà tí ó bá dìde, yóò gbé e mọ́ra. (*Al-Bukhārī*: 494).
- Tí ó bá ń kírun, tí ó wá gbọ́ ẹkún ọmọdé, yóò yára láti kí i, yóò sì ṣe é ní fífúyẹ́. Abū Qatādah gbà á wá pé Ànábí – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wí pé: “Dájúdájú èmi máa ń kírun nígbà mìíràn, tí máa fẹ́ láti fà á gùn, ṣùgbọ́n máa wá gbọ́ ẹkún ọmọdé, máa sì yára nínú ìrun mi, nítorí ìkóríira pé kí ń má fi ara ni ìyá rẹ̀” (*Al-Bukhārī*: 675).

### Àánú rẹ̀ pẹ̀lú àwọn obìnrin:

- Ànábí – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a – gbà wá níyànjú lórí ṣíṣe àmójútó àwọn ọmọbìnrin àti ṣíṣe dáadáa sí wọn, ó sì máa ń wí pé: “Ẹnikẹ́ni tí ó bá jẹ́ alámójútó fún nǹkankan nínú ọ̀ràn àwọn ọmọbìnrin yìí, tí ò sì ṣe dáadáa sí wọn, wọn yóò jẹ́ gàgá fún un níbi iná” (*Al-Bukhārī*: 5649).
- Dájúdájú ó tún kanpá, níbi àsọtẹ́lẹ̀ rẹ̀, mọ́ iwọ̀ ìyàwò, kíka àwọn ọ̀ràn rẹ̀ kún, àti ṣíṣe àmójútó àwọn ìṣesí rẹ̀. Ó tún pa àwọn Mùsùlùmí láṣẹ pé kí apákan wọn máa sọ àsọtẹ́lẹ̀ fún apákejì nípa rẹ̀. Ó wí pé: “Ẹ máa sọ àsọtẹ́lẹ̀ rere fún ara yín nípa àwọn obìnrin” (*Al-Bukhārī*: 4890).



- Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – fi àwọn àpèjúwe tí ó rẹwà jùlọ lélẹ̀ níbi ṣíṣe pẹ̀lẹ́ pẹ̀lú àwọn ará ilé rẹ̀. Tìtí tí ó fi jẹ́ wí pé ó máa ń jókòó síbi ràkúnmí rẹ̀, yóò sì tẹ́ orúnkún rẹ̀ sílẹ̀, Ṣafiyyah – kí Ọlọ́hun yọ́nú sí i – yóò sì gbé orúnkún rẹ̀ lé e ní orúnkún títí tí yóò fi gun ràkúnmí rẹ̀ (*Al-Bukhārī*: 2120).
- Nígbà tí ọmọbìnrin rẹ̀; Fāṭimah – kí Ọlọ́hun yọ́nú sí i – bá wá bá a, ó máa ń gbá ọwọ́ rẹ̀ mú, yóò fi ẹnu kò ó lára, yóò mú un jókòó sí ààyè tí ó jókòó sí (*Abū Dāwūd*: 5217).

**Àánú rẹ̀ pẹ̀lú àwọn ọlẹ:**

- Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – fi gba àwọn ènìyàn níyànjú láti máa gba ọmọ-òrukàn tọ́, ó máa ń wí pé: "Báyìí ni èmi àti alágbàtọ́ ọmọ-òrukàn yóò ṣe wà nínú ọgbà-ìdẹ̀ra Al-Jannah". Ó sì tọ́ka pẹ̀lú ìka ìfábẹ̀lá àti ọba-ààrin, ó sì ya àwọn méjèèjì díẹ̀ (*Al-Bukhārī*: 4998).
- Ó ka ẹni tí ó bá ń náwó lórí obìnrin tí kò ní ọkọ àti tálákà sí bíi ẹni tí ó ń jagun sí ojú-ọ̀nà Ọlọ́hun, àti bíi ẹni tí ń gba ààwẹ̀ ní ọ̀sán, tí ń dìde kírun ní òru. (*Al-Bukhārī:* 5661).
- Ó ka ṣíṣe àànú fún àwọn ọlẹ, àti fífún wọn ní iwọ̀ wọn, ní okùnfà arísìkí àti rírí àrànṣe lórí àwọn ọ̀tà. Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wí pé: "Ẹ bá mi wá àwọn ọlẹ wá; nítorí pé nítorí wọn ní ẹ fi ń rí àrànṣe, tí wọn sí ń pèsè arísìkí fún yín" (*Abū Dāwūd*: 2549).



Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, Muḥammad, ka kíkó àwọn ọlẹ mọ́ra àti ṣíṣe dáadáa sí wọn sí okùnfà ìrànlọ́wọ́ àti arísìkí.



## Ṣíṣe déédé:

- Dájúdájú Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – jẹ́ onídéédé, ó máa ń lo òfin Ọlọ́hun, kódà lórí ẹni tí ó súnmọ́ ọn jùlọ, láti mú àṣẹ Ọlọ́hun, tí ó wà nínú *Al-Qur'ān* ṣẹ: **"Ẹyin ẹni tó gbàgbọ́ lódodo! Ẹ jẹ́ olùdúró sinsin pẹ̀lú déédé ní àwọn olùjẹ́rìí fún Ọlọ́hun, kódà kí ó jẹ́ lórí ẹ̀mí ara yín, tàbí àwọn òbí yín méjèèjì tàbí àwọn ìbátan"** *(An-Nisā'*: 135).
- Ànábí – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a –, nígbà tí ọ̀kan nínú àwọn sàábé wá ṣìpẹ̀ ní ọ̀dọ̀ Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – pé kí wọ́n má fi ìyà jẹ obìnrin pàtàkì kan tí ó jalè, wí pé: "Mo fi Ẹni tí ẹ̀mí Muḥammad wà lọ́wọ́ Rẹ̀ búra, tí ó bá jẹ́ pé Fāṭimah ọmọbìnrin Muḥammad ní ó jalè, dájúdájú màá gé ọwọ́ rẹ̀" (*Al-Bukhārī*: 4053).
- Nígbà tí Ọlọ́hun ṣe jíjẹ èlé ní èèwọ̀ fún àwọn ènìyàn, Ànábí bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ẹni tí ó súnmọ́ ọn jùlọ nínú àwọn ènìyàn, ò sì kọ̀ fún un nípa jíjẹ èlé, òun náà ni arákùnrin bàbá rẹ̀ 'Abbās. Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – sì wí pé: "Àkọ́kọ́ èlé tí máa kọ́kọ́ gbé sílẹ̀ ni; èlé wa, èlé 'Abbās ọmọ 'Abdil-Muṭṭalib, dájúdájú gbogbo rẹ̀ ti di ohun tí a gbé jù sílẹ̀" (Muslim: 1218).
- Ó ṣe é ní òǹdè fún ọ̀làjú àwọn ìjọ àti dídàgbà sókè rẹ̀; kí ọlẹ inú rẹ̀ le gba ẹ̀tọ́ rẹ̀ lọ́wọ́ alágbára láìsí ìbẹ̀rù tàbí ìtàràrà. Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wí pé: "Kí Ọlọ́hun ma fọ ìjọ kan mọ́, tí ọlẹ inú rẹ̀ kò le rí ẹ̀tọ́ rẹ̀ gbà láìsí ìtàràrà" (*Ibn Mājah:* 2426).

## Ṣíṣe dáadáa àti lílawọ́:

- Ọkùnrin kan wá bá a, ó sì tọrọ owó lọ́wọ́ rẹ̀, ó sì dá a lóhùn wí pé: "Ra ohun tí ó bá fẹ́, sísan padà yóò jẹ́ gbèsè tó wà lọ́rùn mi, Ni 'Umar bá wí pé: Ìrẹ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun! Ọlọ́hun kò la ohun tí o kò ní agbára rẹ̀ bọ̀ ọ́ lọ́rùn" Ànábí –kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – kóríira èyí. Ọkùnrin náà sì wí pé: "Máa náwó, má ṣe bẹ̀rù òsì kankan láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun, Ọba Onítẹ̀ẹ́-ọlá". Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a- rẹ́rìnín músẹ́, wọ́n sì rí àmì ìdùnnú ní ojú rẹ̀" (*Al-'Aḥādīthul-Mukhtārah: 88*).
- Wọ́n gbé ọgọ́rin ẹgbẹ̀rún owó Dirham wá bá a, ó sì gbé e sí orí ẹní, lẹ́yìn náà ó wá síbẹ̀, ó sì pín in, kò dá ọníbééèrè kankan padà títí tí ó fi pín in tán (*Al-Ḥākim*: 5423).

Àwọn àkọsílẹ̀ ìpìlẹ̀ fi yé wa pé Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn *Islām* rán kò kó ọ̀rọ̀ jọ ní ìgbà-ayé rẹ̀.



## Sùúrù àti àfaradà Rẹ̀:

- Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – jade pẹ̀lú ìbànújẹ́ kúrò ní ìlú Ṭā'if (ìlú tí òkè pọ̀ níbẹ̀, ó fi 90 kilò jìnnà sí ìlú Makkah) lẹ́yìn ìgbà tó lọ sìbẹ̀ láti pé wọ́n sí ẹ̀sìn Islām, wọ́n fi ṣùtá kàn án, wọ́n sì dá a lóhùn ní ọ̀nà tó burúkú júlọ. Ní ìgbà tó ń padà sí ìlú Makkah, ibẹ̀ sì ni àwọn ènìyàn rẹ̀ tí wọ́n lé kúrò nílé, tí wọ́n fi ṣùtá kàn án wà, Ọlọ́hun rán ọ̀kan nínú àwọn *Malā'ikah* sí i, pé kó bi í léèrè pé ṣé ó fẹ́ kí Ọlọ́hun pa àwọn ará ìlú Ṭā'if run. Ó sì wí pé: Rárá! Mo fẹ́ kí Ọlọ́hun mú jáde láti ìbàráàdí wọn; ẹni tí yóò máa jọ́sìn fún Ọlọ́hun nìkan ṣoṣo, tí kò ní fi nǹkankan ṣẹbọ pẹ̀lú Rẹ̀" (*Al-Bukhārī*: 3059).
- Ohun tó tóbi ju èyí lọ ni ipò tó wà pẹ̀lú àwọn ara ìlú Makkah, àwọn tó lé e kúrò ní ìlú rẹ̀, tó tún jẹ́ wí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà ni wọ́n ti fi ẹnu wọn àti idà wọn ṣe é ní ṣùtá. Wọn kò sì fi agbára wọn kankan pamọ́ láti kó ìparun bá òun àti àwọn tó wà pẹ̀lú rẹ̀ fún ọdún gbọọrọ. Nígbà tí àrànṣe dé láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun, tí Ọlọ́hun, mímọ́ ni fún Un, fún un ní agbára pẹ̀lú ṣíṣẹ́gun ìlú Makkah, tí ó sì jẹrí gbogbo wọn pátápátá, ó dìde nàró láàrin wọn, ó sí wí pé: "Kín ni ohun tí ẹ lérò pé màá ṣe pẹ̀lúyín?". Wọ́n dáhùn pé: Dáadáa ni, ìrẹ arákùnrin wa alápọ̀n-ọ́nlé, ọmọ arákùnrin wa alápọ̀n-ọ́nlé. Ó wí pé: "Màá sọ gẹ́gẹ́ bí ọmọ-ìyá mi Yūsuf – èyí ni Ànábì Ọlọ́hun, Yūsuf ọmọ Ya'qūb, ẹni tó ṣe àmójúkúrò fún àwọn arákùnrin rẹ̀ tí wọ́n ṣe é ní ṣùtá, tí wọ́n sì jù ú sínú kọ̀nga – ti sọ́, ó sọ fún wọn pé: Kò sí ìjìyà fun yín ní òní. Ọlọ́hun yóò ṣe àforíjìn fun yín, Òun náà sì ni Aláánú, tí àánú Rẹ̀ ju ti gbogbo aláánú lọ. (Yūsuf: 92). Ẹ̀ máa lọ, ẹ ti di ẹni tí a tú sílẹ̀" (*Al-Bayhaqī*: 18275).





## Rírí ayé sá:

- Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – máa ń lo ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun Ọba rẹ̀, Ọba Abiyì, tí Ó gbọn-n-gbọ́n, ní gbogbo ìgbà: **{Àti pé má ṣe fẹ ẹyinjú rẹ méjèèjì sí ohun ti A fi ṣe ìgbádùn fún àwọn ìjọ kan nínú wọn, yòdòyindin ìṣẹ̀mí ayé, nítorí kí Á le dan wọ́n wò nínú rẹ̀. Ìpèsè Ọlọ́hun Ọba rẹ ni ó sì dára jùlọ, ni ó sì tún wà gbére jùlọ}** (*Ṭahā*: 131).
- Sàábé rẹ̀ 'Umar – kí Ọlọ́hun yọ́nú sí i – wọlé tọ̀ ọ́ ní ọjọ́ kan, ni ó bá rí i pé ó fi ẹ̀gbẹ́ lélẹ̀ lórí ẹní, kò sí ìtẹ́ kankan láàrin òun àti ẹ̀, ó sì ti lapa ní ẹ̀gbẹ́ rẹ̀, 'Umar sì wí pé: Mo gbé ojú mi sókè nínú ilé rẹ̀, mo fi Ọlọ́hun búra, mi ó rí nǹkankan tí ó yẹ kí n ran ojú mọ́, tí ó sì bùkáátà sí bíbo ojú wò. Mo sì wí pé: Bẹ Ọlọ́hun, kí Ó jọ̀wọ́ kí Ó ṣe arísìkí tó gbààyè fún ìjọ rẹ̀, nítorí pé dájúdájú àwọn Fāris àti Rūm, Ó ṣe arísìkí tó gbààyè fún wọn, wọ́n sì fún wọn ní ayé, wọn kì í sì sin Ọlọ́hun. Ó sì wí pé: Ṣé ò ń bẹ nínú iyèméjì ni, ìrẹ ọmọ Al-Khaṭṭāb? Àwọn wọ̀nyẹ jẹ́ ìjọ tí wọ́n ti kánjú fún wọn ní dáadáa wọn nínú ìṣẹ̀mí-ayé yìí". (*Al-Bukhārī*: 2336).
- Ó máa ń sọ wí pé: "Kín ni ohun tó kàn mí pẹ̀lú ilé-ayé, èmí kò jẹ́ nǹkankan nínú ilé-ayé bíkòse bíi àpèjúwe ẹni tó gun nǹkan, tó gba òjìji ní abẹ́ igi kan, lẹ́yìn náà ó tẹ̀ síwájú, ó sì fi sílẹ̀. (*At-Tirmidhī*: 2377).
- Oṣù kan, méjì, mẹ́ta a máa rékọjá pẹ̀lú rẹ̀, tí wọn kò ní dá iná oúnjẹ kankan nínú àwọn ilé Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun. Dàbínú àti omi nìkan ni yóò máa jẹ. (*Al-Bukhārī*: 2428). Ní ìgbà mìíràn ó le wà lórí ebi fún odidi ọjọ́ kan, tí kò si ní rí dàbínú tí kò dára èyí tí ó le yó o. (Muslim: 2977). Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – kò jẹ búrẹ́dì tí wọ́n ṣe látara álíkámà yó fún ọjọ́ mẹ́ta tẹ̀lé ara wọn rí títí tí Ọlọ́hun fi gba ẹ̀mí rẹ̀, búrẹ́dì tó pọ̀ jùlọ tó máa ń jẹ ní èyí tí wọ́n fi jéró ṣe (*Muslim*: 2976).

> Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn Islām rán ṣe àfijọ ìṣesí rẹ̀ pẹ̀lú ilé-ayé pẹ̀lú pé ó dá bíi arìnrìn-àjò tí ó jókòó sí abẹ́ òjìji igi kan, lẹ́yìn náà ó kúrò níbẹ̀, ó sì pa á ti..




## Pípé àdéhùn:

- Pípé àwọn àdéhùn jẹ́ ara àwọn ìwà tó ga jùlọ, tó sì biyì jùlọ. Ipò rẹ̀ máa ń ga sí i nínú ẹ̀mí, nígbà tó bá jẹ́ ohun tó fà á ni fífi dáadá san dáadáa, tí kò sí àdéhùn kankan tó pọn dandan láàrin àwọn méjèèjì. Dájúdájú èyí ni ìṣesí Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, ó máa ń dá dáadáa padà pẹ̀lú ohun tó tóbi ju èyí tí wọ́n ṣe sí i lọ, kódà kó jẹ́ wí pé kò sì àdéhùn tàbí àfẹnukò kankan lórí rẹ̀, wáá wòye sí ká ní ó wà.
- Nígbà tí Hiraql, ọba àwọn Kìrìsìtẹ́ni, bi àwọn kèfèrí ìran Quraysh léèrè nípa àwọn ìròyìn Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –, ó wí pé: Ṣé ó máa ń jàǹbá bí? Wọ́n dáhùn pé: Bẹ́ẹ̀ kọ́. Ó sì sọ fún wọn pé: Báyìí náà sì ni àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, wọn kì í jàǹbá. (*Al-Bukhārī: 7*).
- Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn Islām rán wà ní ipò tí ó ga jùlọ níbi pípé iwọ̀ ìyàwó rẹ̀ àkọ́kọ́, Khadījah, lẹ́yìn ikú rẹ̀, ó ṣ́ọ ipò rẹ̀ fún un, ó mọ oore lórí ipa tí ó kó, ó sì ṣe ojúkòkòrò ṣíṣé àpọ́nlé fún àwọn alásúnmọ́ rẹ̀ àti àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀..
- ‘Ā’ishah, ìyàwó Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – fún wa ní ìrò nípa àdéhùn rẹ̀ fún ìyàwó rẹ̀ àkọ́kọ́, Khadījah, èyí tó kú nígbà tí Ọlọ́hun ṣẹ̀ṣẹ̀ gbé e dìde fún ìgbà àkọ́kọ́, tí ‘Ā’ishah kò sì mọ̀ ọ́n, ó wí pé: Dájúdájú Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – máa ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ ní ọ̀pọ̀lọpọ̀. Ní ìgbà mìíràn yóò pa ẹran, yóò yọ ọ́ ní burè burè, lẹ́yìn náà yóò fi ránṣẹ́ sí àwọn ọ̀rẹ́ Khadījah. Nígbà mìíràn, mo máa ń sọ fún un pé: Bíi ẹni wí pé kò sí obìnrin kankan ní ayé mọ́ àyàfi Khadījah nìkan? Yóò sì dáhùn pé: Dájúdájú ó jẹ́ báyìí, ó tún jẹ́ báyìí..yóò sì máa mẹ́nu bá ara àwọn ìròyìn àrà-ọ̀tọ̀ rẹ̀”. (*Al-Bukhārī:* 3607).
- Àwọn àlejò kan, ní ọjọ́ kan, wá sí ọ̀dọ̀ rẹ̀ láti ọ̀dọ̀ An-Najāshī (èyí tí í ṣe ọba ìlú Ḥabashah, ó sì jẹ́ odi-ìṣọ́ fún àwọn Mùsùlùmí ní ìgbà tí ẹ̀sìn Islām ṣẹ̀ṣẹ̀ dé). Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – dìde nàró, ó sì ń ṣe wọ́n ní àlejò fún ara rẹ̀, ní àwọn sàábé rẹ̀ bá sọ fún un pé: Àwa ti tó láti bá ọ ṣe é, ó sì wí pé: “Dájúdájú wọ́n ṣe àpọ́nlé fún àwọn sàábé mi, èmí náà sì fẹ́ràn kí n san án pé padà fún wọn” (*Shu‘abul-’Īmān*: 8704).

Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – fi àwọn àpèjúwe tí ó rẹwà jùlọ lélẹ̀ níbi àwọn ìhùwàsí tó dára níbi gbogbo agbegbe ìṣẹ̀mí-ayé láti fi mímú àṣẹ Ọlọ́hun lò rinlẹ̀ àti láti kọ́ṣe àwọn Ànábí alápọ̀n-ọ́nlé tó síwájú rẹ̀.

Mọ̀ṣáláṣí Ànábì Muḥammad, èyí tí ó kọ́ sí ìlú *Madīnah* tàbí ìlú *Madīnah* oní-ìmọ́lẹ̀, gẹ́gẹ́ bí àwọn Mùsùlùmí ṣe máa ń pè é. Èyí ni ìlú mímọ́, tí ó pàtàki sìkejì lẹ́yìn ìlú *Makkah*. Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, Muḥammad, ṣe hijrah lọ síbẹ̀, ó sì kọ́ Mọ̀ṣálàṣí rẹ̀ síbẹ̀, wọ́n sì sin ín síbẹ̀. Ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ mílíọ̀nù nínú àwọn Mùsùlùmí ni ó máa ń bẹ Mọ̀ṣálàṣí yìí wò ní ọdọọdún.





# Díẹ̀ nínú àwọn ọ̀rọ̀ Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –

Àwọn Mùsùlùmí ka gbígba àwọn ọ̀rọ̀ Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wá kún, bóyá títẹ́tí sí i tàbí kíkọ ọ́ sílẹ̀. Àwọn olùhán nǹkan àti àwọn onímímọ̀ sì gbìyànjú nípa díde àti ṣíṣàlàyé àwọn gbólóhùn rẹ̀. Wọ́n mú wá fún gbogbo àgbáyé; ètò tó ba ènìyàn lẹ́rù, níbi fífi ẹsẹ̀ àwọn ẹ̀gbàwá rinlẹ̀. Àti níbi mímọ èyí tó fi ẹsẹ̀ múlẹ̀ àti èyí tí kò fi ẹsẹ̀ múlẹ̀, títí kan àwọn àlàyé tó kún nípa àwọn ọ̀rọ̀ àti àwọn gbólóhùn, àti nípa ohun tí wọ́n fi kún un àti ohun tí kì í ṣe ara rẹ̀.

**Ìwọ̀nyí ni àwọn àpèjúwe nínú àwọn ẹ̀gbàwá *Ḥadīth* Ànábí, èyí tí Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, Muḥammad sọ:**

- “Gbogbo iṣẹ́ pẹ̀lú àníyàn ni, àti pé dájúdájú àníyàn tí kálukú bá dà ní yóò jẹ́ ti ẹ̀” (*Al-Bukhārī:* 1).
- “Dáadáa ni ìwà rere, ẹ̀ṣẹ̀ sì ni ohun tí ẹ̀mí rẹ ń ṣe ròyíròyí nípa rẹ̀, tí o sì kórìíra kí àwọn ènìyàn mọ̀ nípa rẹ̀” (*Muslim*: 2553).
- “Rí ayé sá, Ọlọ́hun yóò fẹ́ràn rẹ. Tún rí ohun tó wà lọ́wọ́ àwọn ènìyàn sá, àwọn ènìyàn sì yóò fẹ́ràn rẹ” (*Ibn Mājah*: 4102).
- “Àpèjúwe èmi àti àwọn Ànábí tó síwájú mi, dà bíi àpèjúwe ọkùnrin kan tó kọ́lé kan, tó kọ́ ọ dáadáa, tó bu ẹwà kún un àyàfi ààyè bíríkì kan ní abala kan. Àwọn ènìyàn sì bẹ̀rẹ̀ síní rọkiri ká a, ó sì ń jọ wọ́n lójú, wọ́n sì ń sọ wí pé: Èése tí wọn kó gbé bíríkì yìí sí i?! Nítorí náà èmi ni bíríkì náà, èmi náà sí ni ìgbẹ̀yìn àwọn Ànábí” (*Al-Bukhārī*: 3342).
- “Mùsùlùmí ni ẹni tí àwọn Mùsùlùmí là níbi ahọ́n rẹ̀ àti ọwọ́ rẹ̀, àti pé olùyandì ni ẹni tó yan ohun tí Ọlọ́hun kọ̀ nípa rẹ̀ lódì” (*Al-Bukhārī*: 10).
- “Bẹ̀rù Ọlọ́hun níbi kíbi tí ó bá wà, tún máa fi dáadáa tẹ̀lé àìda, yóò pa á rẹ́, sì máa bá àwọn ènìyàn lò pẹ̀lú ìwà tó dára” (*At-Tirmidhī*: 1987).
- “Ẹ tẹ́tí gbọ́, ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe àbòsí fún ẹni tí kì í ṣe Mùsùlùmí, tàbí ó gbé ohun tí ipá rẹ̀ kò ká kọ́ ọ lọ́rùn, tàbí ó gba nǹkan lọ́wọ́ rẹ̀ láìṣe wí pé inú rẹ̀ dùn si, èmi ni máa jẹ́rìí takò ó ní ọjọ́ Ìgbénde” (*Abū Dāwd:* 3052).
- “Àwọn aláánú, Ọlọ́hun, Ọba Àjọkẹ́ Ayé yóò ṣe àànù fún wọn. Nítorí náà ẹ máa ṣe àànù fún àwọn tí ń bẹ lórí ilẹ̀, Ẹni tí ń bẹ ní sánmà yóò ṣe àànù fún yín” (*Abu Dāwūd:* 4941)
- “Ẹnikẹ́ni tó bá mú ìnira kan nínú ìnira ilé-ayé kúrò fún olùgbàgbọ́ òdodo, Ọlọ́hun yóò gbé ìnira kan nínú ìnira ọ̀run kúrò fún un. Ẹnikẹ́ni tó bá ṣe ìdẹ̀ra fún ẹni tí ara ń ni, Ọlọ́hun yóò ṣe ìdẹ̀ra fún un ní ayé àti ọ̀run. Ẹnikẹ́ni tó bá bo Mùsùlùmí kan ní àṣírí, Ọlọ́hun yóò bò ó ní àṣírí ní ayé àti ọ̀run. Ọlọ́hun yóò máa ran ẹrúsìn Rẹ̀ lọ́wọ́ ní òpin ìgbà tí ẹrúsìn Rẹ̀ náà bá ń ran ọmọ-ìyà rẹ̀ nínú ẹ̀sìn lọ́wọ́. Ẹnikẹ́ni tí ó bá tọ ọ̀nà kan; tí ó ń wá ìmọ̀- ẹ̀sìn níbẹ̀, Ọlọ́hun yóò tìtorí rẹ̀ rọ ọ̀kan nínú àwọn ọ̀nà ọgbà-ìdẹ̀ra Àlùjáńnà fún un. Ẹnikẹ́ni tí iṣẹ́ rẹ̀ fà sẹ́yìn, ìran rẹ̀ kò le yára fà á síwájú” (*Muslim* 2699).



“Kì í ṣe ara wa ni; ẹni tí kì í kẹ́ ọmọdé wa, tí kò sì mọ iwọ̀ àgbàlagbà wa” (*At-Tirmidhī:* 1920).






“Ẹ kò le wọ ọgbà-ìdẹ̀ra Al-Jannah títí tí ẹ ó fi gbàgbọ́ lódodo, ẹ kò sì le gbàgbọ́ lódodo títí tí ẹ ó fi fẹ́ràn ara yín. Ṣé kí n tọ́ka yín sí nǹkankan, tí ó jẹ́ wí pé tí ẹ bá ṣe é, ẹ ó fẹ́ràn ara yín? Ẹ máa fọ́n sálámà ká láàrin ara yín” (*Muslim*: 54).

- “Ẹnikẹ́ni tí ó bá lù jìbìtì, kì í ṣe ara wa” (*At-Tirmidhī:* 1315).
- “Àpèjúwe àwọn olùgbàgbọ́ òdodo, níbi níní ìfẹ́ ara wọn, kíkẹ́ ara wọn àti níní àánú ara wọn, ó dà bíi àpèjúwe ara kan ṣoṣo, tí ó ṣe wí pé, tí oríkèé kan nínú rẹ̀ bá ń ké ìrora, gbogbo ara yóò gbà á pẹ̀lú dídá oorun mọ́jú àti gbígbóná” (*Muslim:* 2586).
- “Gbogbo yín ni adaranjẹ̀, gbogbo yín ni wọn yóò sì bi léèrè. Adaranjẹ̀ ni adarí ìlú, wọn yóò bi í léèrè. Adaranjẹ̀ ni ọkùnrin nínú ẹbí rẹ̀, wọn yóò bi í léèrè. Adaranjẹ̀ ni obìnrin náà jẹ́ nínú ilé ọkọ rẹ̀, wọn yóò bi í léèrè. Ẹ tẹ́tí gbọ́, gbogbo yín ni adaranjẹ̀, gbogbo yín ni wọn yóò sì bi léèrè” (*Al-Bukhārī*: 4892).
- “Ẹni tí ó dára jùlọ nínú yín ni ẹni tí ó dára jùlọ nínú yín sí àwọn ara ilé rẹ̀, èmí ni mo sì dára jù yín lọ sí àwọn ara ilé mi” (*At-Tirmidhī*: 3895).
- “Láàrin ìgbà tí ọkùnrin kan ń rìn lọ ní ojú-ọ̀nà kan, òǹgbẹ gbẹ ẹ́ gidi gan, ó wá rí kọ̀nga kan, ó wọnú rẹ̀, ó sì mumi. Lẹ́yìn náà ó jáde, ó sì rí ajá kan tí ó ń mí hẹlẹhẹlẹ, tí ó ń jẹ àbàtà látara òǹgbẹ. Ní ọkùnrin náà bá wí pé: Dájúdájú òǹgbẹ ti mú ajá yìí kákà, gẹ́gẹ́ bí irú èyí tí ó mú mi, nítorí náà ó wọnú kọ̀nga, ó kún ìbọ̀sẹ̀ aláwọ rẹ̀ pẹ̀lú omi, lẹ́yìn náà ó dì í mú pẹ̀lú ẹnu rẹ̀, títí tí ó fi gùnkè, ó sì fún ajá náà ní omi mu. Nítorí náà Ọlọ́hun dúpẹ́ fún un, Ó sì ṣe àforíjìn fún un” Wọn wí pé: Ìrẹ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun! Ṣé ẹ̀san rere tún ń bẹ fún wa níbi àwọn ẹranko ni? Ó wí pé: “Ẹ̀san rere ń bẹ níbi gbogbo ẹ̀dọ̀ tútù” (*Al-Bukhārī*: 2266).
- “Àmì alágàbàgebè mẹ́ta ni”. Nínú ohun tí ó kà mọ́ ọn ni: “Nígbà tí ó bá ṣe àdéhùn, yóò já a” (*Al-Bukhārī*: 33)
- “Nínú dídára ẹ̀sìn Islām èèyàǹ, ni kí ó pa ohun tí kò kàn án tì” (*At-Tirmidhī*: 2317).
- “Dájúdájú Ọlọ́hun fẹ́ràn ṣíṣe pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ níbi gbogbo nǹkan pátápátá” (*Al-Bukhārī*: 5678).
- “Ẹnikẹ́ni tí wọ́n bá ṣe ṣíṣe pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ ní èèwọ̀ fún, wọ́n yóò ṣe oore ní èèwọ̀ fún un” (*Muslim*: 2592).

**Báwo ni *Al-Qur'ān* ti ròyìn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, Muḥammad – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a –?**

*Al-Qur'ān* sọ ìdàkejì agbegbe kan tó ya ènìyàn lẹ́nu nípa irú ẹ̀dá tí Ànábì jẹ́ àti bí ó ti máa ń lò pẹ̀lú àwọn tó wà ní àyíká rẹ̀, àwọn ìwà rẹ̀, àwọn ìròyìn ẹwà àti irú ènìyàn tó jẹ́, yóò hàn kedere nínú rẹ̀ lẹ́ẹ̀kan náà:

- Ìkẹ́ ni ó jẹ́ fún gbogbo àgbáyé **"A kò rán ọ bíkòṣe láti jẹ́ ìkẹ́ fún gbogbo àgbáyé"** (*Al-'Anbiyā'*: 107), kì í ṣe fún àwọn Mùsùlùmí nìkan.
- Ó wà lórí ìwà tóbi **"Àti pé dájúdájú ìwọ ń bẹ lórí ìwà tóbi"** (*Al-Qalam*: 4).
- Ó máa ń ṣe ojú kòkòrò tó lágbára jùlọ lórí ìmọ̀nà àwọn ènìyàn, ó sí máa ń banújẹ́ gidigidi lórí anù wọn. Débi wí pé wọ́n kàn án nípa fún un pé ohun tó pàtàkì fún un ni pípèpè àti mímú iṣẹ́ dé ògóngó àti pé dájúdájú Ọlọ́hun yóò fi ẹni tó bá fẹ́ ṣe kòngẹ́ ìmọ̀nà. "Nítorí náà bóyá o le fi apákan ohun tí a fi ranṣẹ si ọ sílẹ̀, tí waa si fún ẹ̀mí rẹ pinpin pẹ̀lú rẹ nítorí pé wọn wí pé: Kílódé tí wọn ko sọ pẹpẹ orọ kalẹ fún un. Tàbí ki ọkan nínú àwọn Malā'ikah de pẹ̀lú rẹ? Dájúdájú olukilọ ni iwọ jẹ. Ọlọ́hun si jẹ Oluṣọ lórí gbogbo nǹkan" (Hūd: 12). "Àti pé ti Ọlọ́hun ba fẹ ni, wọn i bá tí ṣẹbọ. A kò si ṣe ọ ni oluṣọ le wọn lórí, o ki i si ṣe olutọju ohun-ìní wọn" (Al-'An'ām: 107). **"Wí pé: Ògédé abara bí irú yín ni èmi jẹ́, wọ́n ń ránṣẹ́ sí mi pe dájúdájú Ọlọ́hun yin, Ọlọ́hun kan ṣoṣo ni. Nítorí náà ẹnikẹ́ni tí ó ba n rankan Ipàdé Ọlọ́hun Ọba rẹ ki o yaa máa ṣe iṣẹ́ daadaa, ki o si ma ṣe ẹbọ kankan pẹ̀lú ìjọsìn fún Ọlọ́hun Ọba rẹ"** (*Al-Kahf*: 110).
- Ó máa ń wá àwáwí fún àwọn ẹlòmíràn, ó sì máa ń gbé ojú kúrò ní àwọn àṣìṣe wọn. **"Ọlọ́hun ti ṣe amojukúrò fún ọ. Kílódé tí ó fi yọnda fún wọn (láti wọnyìn) titi ti àwọn ẹni tí wọn sọ òdodo yóò fi han si ọ, tí waa si tún mọ àwọn opurọ?"** (*At-Tawbah*: 43).
- Ó máa ń bẹ̀ Ọlọ́hun pé kí Ó ṣe àforíjìn fún àwọn ọ̀tá rẹ̀ títí tí wọ́n fi kọ̀ fún un nípa rẹ̀ **"(Bóyá) o tọrọ aforijin fún wọn tàbí o ko tọrọ aforijin fún wọn, tí ó ba tọrọ aforijin fún wọn nígbà aadọrin, Ọlọ́hun kò ní ṣe aforijin fún wọn. Eléyìí jẹ titori pe dájúdájú wọn ti ṣe àìgbàgbọ́ pẹ̀lú Ọlọ́hun àti Iranṣẹ Rẹ. Ọlọ́hun kò sì ni fi ọ̀nà mọ àwọn pòkî ènìyàn"** (*At-Tawbah*: 80).
- Ohun tó bá jẹ́ ìnira fún àwọn olùgbàgbọ́ òdodo máa ń jẹ́ ìnira fún un, ó sì jẹ́ alàánú, onikẹ́ẹ́ pẹ̀lú wọn. **"Dájúdájú Iranṣẹ kan ti de wa ba yin láti inu ẹ̀mí ara yin, ohun tí ó jẹ inira fun yín jẹ inira fún un, o jẹ oluṣe ojukokoro lórí yin (láti ri oore lọ́dọ̀ Ọlọ́hun), pẹ̀lú àwọn olùgbàgbọ́ òdodo, o jẹ alàánú, onikẹ́ẹ́"** (*At-Tawbah*: 128)
- Nígbà mìíràn, dídúró apákan àwọn èèyàn sínú ilé rẹ̀ máa ń kó ìnira bá a, ṣùgbọ́n ìtìjú kò ní jẹ́ kí ó sọ fún wọn. **"Ẹyin ẹni ti o gbàgbọ́ lódodo! Ẹ ma ṣe máa wọ àwọn ile Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun àyàfi tí wọn ba yọnda fun yín fún ounjẹ kan laimáa reti jíjiná rẹ. Ṣùgbọ́n nígbà tí wọn bá pe yin, ẹ yaa wọle, nígbà tí ẹ ba si ti jẹun tan, ki ẹ tuka laijokoo kalẹ fún ọrọ kankan. Dájúdájú ìyẹn máa n ko ṣùtá ba Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun, tí ó sì ń tiju yin, ṣùgbọ́n Ọlọ́hun ki i tiju nípa òdodo. Àti pé nígbà tí ẹ ba n bi wọn leere nǹkan, ẹ yaa bi wọn leere láti ẹyin gàgá. Ìyẹn ni o mọ́ jùlọ fún ọkan yin àti ọkan wọn. Àti pé ko lẹtọọ fun yín pe ki ẹ máa ṣẹ Iranṣẹ Ọlọ́hun ni ṣùtá àti ki ẹ fẹ àwọn ìyàwó rẹ lẹ́yìn rẹ laelae. Dájúdájú ìyẹn jẹ ohun tí ó tóbi lọ́dọ̀ Ọlọ́hun"** (*Al-'Aḥzāb*: 53).
- Ó jẹ́ ènìyàn pẹ̀lẹ́, ẹni tó ní àmójúkúrò, ẹni tí ọkàn rẹ̀ rọ̀, ó máa ń bá àwọn sàábé rẹ̀ lò pẹ̀lú pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́, ó sì máa ń gba ìmọ̀ràn ní ọ̀dọ̀ wọn, ó sì máa ń lo ìmọ̀ràn wọn, kódà ní ìgbà tí nǹkan bá díjú àti ìgbà tí nǹkan bá le koko jùlọ. **"Àti pé pẹ̀lú àánú láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun ni o fi rọ fún wọn, tí ó ba si ṣe pe o jẹ oni iwa buruku, ọlọkan lile ni, dájúdájú wọn ko ba ti fọnka kúrò lọ́dọ̀ rẹ. Nítorí náà ṣe amojukúrò fún wọn, ki o si tọrọ afọrijin fún wọn, ki o si tún gba imọran lọ́dọ̀ wọn. Nígbà tí o ba ti wa pinnu, yaa gbe ara le Ọlọ́hun. Dájúdájú Ọlọ́hun fẹran àwọn olugbara le (E)"** (*'Āl-'Imrān:* 159).



# *Al-Qur'ān* alápọ̀n-ọ́nlé jẹ́ iṣẹ́-ìyanu gbére fún ẹ̀sìn *Islām*

Kín ni *Al-Qur'ān*, èyí tó jẹ́ wí pé ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó máa ń gbawájú gẹ́gẹ́ bíi ìwé tó tà jùlọ, tó sì kàákiri jùlọ ní gbogbo àgbáyé? Ohun tó lé ní bílíọ̀nù kan àti ààbọ̀ Mùsùlùmí sì gbà á gbọ́?

## *Al-Qur'ān* ni Tírà mímọ́ àwọn Mùsùlùmí, èyí tí wọ́n gbàgbọ́ pé dájúdájú òun ni:


- Ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun, èyí tí Ó sọ̀kalẹ̀ fún Ìránṣẹ́ Rẹ̀, Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – láti jẹ́ ìmọ̀nà àti ìmọ́lẹ̀ fún àwọn ènìyàn.
- Òun ni ìgbẹ̀yìn àwọn Tírà tó sọ̀kalẹ̀ láti sánmà.
- Èyí tí Ọlọ́hun ṣọ́ kúrò níbi yíyí i padà tàbí pípaàrọ̀ rẹ̀.
- Òun ni a máa ń fi kíké e àti híhá a ṣe ìjọsìn, gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ wí pé àwọn ẹ̀dá tùn máa ń fi lílo àwọn ìdájọ́ àti òfin rẹ̀ ṣe ìjọsìn.

Dájúdájú sísọ̀kalẹ̀ rẹ̀ bẹ̀rẹ̀ láti ipasẹ̀ Jibrīl – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – lẹ́yìn tí Ànábì ti pé ọmọ ogójì ọdún, àkọ́kọ́ *āyah* tó sọ̀kalẹ̀ ni (Ké! Pẹ̀lú Orúkọ Ọlọ́hun Ọba rẹ, Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá (gbogbo ẹ̀dá)). Ó sì sọ̀kalẹ̀ ní ìsọ̀rí, ìsọ̀rí, fún ọdún mẹ́tàlélógún ní ìbámu sí àwọn ìṣesí àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀.

> *Āyah* àkọ́kọ́ tí ó sọ̀kalẹ̀ nínú *Al-Qur'ān* ni (Ké! Pẹ̀lú Orúkọ Ọlọ́hun Ọba rẹ, Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá (gbogbo ẹ̀dá)). Ó sì sọ̀kalẹ̀ ní ìsọ̀rí, ìsọ̀rí, fún ọdún mẹ́tàlélógún ní ìbámu sí àwọn ìṣesí àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀.

*Al-Qur'ān pín* sí *Sūrah* 114, àwọn àkòrí ọ̀rọ̀ rẹ̀ àti àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ rẹ̀ yàtọ̀ sí ara wọn. Ṣùgbọ́n gbogbo rẹ̀ pátá, papọ̀ níbi ipò tó ga jùlọ níbi ìgbọ́rọ̀kalẹ̀ àti èdè Lárúbáwá tó dá nítọ̀. Ó sì dá lórí fífi àwọn ènìyàn mọ̀nà àti pípè wọ́n sí mímáa jọ́sìn fún Ọlọ́hun nìkan ṣoṣo.

### Nínú àwọn agbegbe tó pàtàkì jùlọ, èyí tí *Al-Qur'ān* sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ ni:



1- Fífi jíjẹ́ Ọ̀kan ṣoṣo Ọlọ́hun rinlẹ̀, àti bíba àwọn ìrújú àwọn tó ń ṣe ẹbọ pẹ̀lú Rẹ̀ jẹ́.

2- Ìtàn àwọn Ànábì àti àwọn ìjọ tó ti lọ.

3- Pípèpè sí ríronú sí ilé-ayé tó gbààyè yìí àti wíwòye sí àwọn ẹ̀dá tó wà ní àyíká wa, àti kíka díẹ̀ nínú ìdẹ̀ra Ọlọ́hun lórí wa.

4- Ṣíṣàlàyé àwọn òfin ẹ̀sìn Islām àti àwọn ohun tí Ọlọ́hun pàṣẹ rẹ̀ àti àwọn ohun tí Ó kọ̀ nípa rẹ̀.

5- Àlàyé nípa ìròyìn àwọn olùgbàgbọ́ òdodo àti ìwà wọn, àti ìkìlọ̀ nípa àwọn ìròyìn burúkú.

6- Ọ̀rọ̀ nípa ọjọ́ ìkẹyìn àti ẹ̀san àwọn ẹni dáadáa àti àwọn ẹni burúkú.

7- Ríre àwọn olùgbàgbọ́ òdodo láti ipasẹ̀ àlàyé lórí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀, èyí tó ń ṣẹ̀lẹ̀ sí Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – àti àwọn sàábé rẹ̀.

**Èyí ni àlàyé ránpẹ́ nípa apákan nínú àwọn ìròyìn àrà-ọ̀tọ̀ *Al-Qur'ān* àti àwọn ohun ẹ̀ṣà rẹ̀..**






## Ìṣẹ́ ìyanu tí ń bẹ níbi ṣíṣọ́ ọ:

Ọlọ́hun sọ ìgbẹ̀yìn àwọn Tírà Rẹ̀ ní *Al-Qur'ān*, láti tọ́ka sí pé ó jẹ́ Tírà tí a ó máa ké, tí a ó sì máa há sínú àwọn igbá-àyà. Ó tún sọ ọ́ ní *Al-Kitāb* nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn āyah, láti tọ́ka sí kíkọ ọ́ àti ṣíṣọ́ ọ sínú àwọn tákàdá. Dájúdájú Ọlọ́hun dá ààbò bo *Al-Qur'ān* pẹ̀lú nǹkan méjèèjì yìí lápapọ̀. Nítorí náà nígbà tí nǹkankan nínú rẹ̀ bá sọ̀kalẹ̀, wọn yóò kọ ọ́ ní ìsejú rẹ̀, wọn yóò sì há a láti ẹnu rẹ̀. A kì í gba ẹ̀rí àwọn tó há a, bí ó ti wulẹ̀ kó pọ̀ tó, tí kò bá ti bá ohun tí wọ́n kọ sílẹ̀ mu. A kì í sì gba ohun tí wọ́n kọ sílẹ̀, ní òpin ìgbà tí kò bá ti bá ohun tí wọ́n wọ́n há a láti ẹnu Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun mu..

Nígbà tí àwọn onímímọ̀ jíjẹ́ Ọlọ́hun lọ́dọ̀ àwọn Kìrìsìtẹ́ni fi rinlẹ̀ pé dájúdájú títako ara wọn, èyí tó wáyé nínú àwọn Bíbélì, kò sí ohun titun níbẹ̀, ohun tí à ń retí ṣíṣẹlẹ̀ rẹ̀ ni, nítorí yíyàtọ̀ àwọn ibi tí àwọn tó kọ Bíbélì ti mú ohun tí wọ́n kọ, àti yíyàtọ̀ àsìkò wọn, àti ọ̀nà iṣẹ́-ìránṣẹ́ tí kò lọ sàn án èyí tí àwọn Bíbélì kó sínú, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé, nínú ìwòye wọn, wọ́n gbà pé àsán pé ó kó ohun tí ìmọ̀nà wà nínú rẹ̀ fún àwọn ènìyàn sínú ti tó àwọn.

Ṣùgbọ́n pàápàá, èyí tí kò rọrùn fún ẹni tó ń kà á, tó jẹ́ onídéédé, àyàfi kí ó gbà bẹ́ẹ̀ ni wí pé dájúdájú *Al-Qur'ān* pa sófo tán pátápátá níbi èyíkéyìí kí nǹkan tako ara wọn tàbí kí nǹkan má bá ara wọn mu. Ìdí èyí ni pé; gbólóhùn àti ìtumọ̀ rẹ̀ Ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun, Ọba Abiyì, tí Ó gbọn-n-gbọ́n ni. Wọ́n há a sórí, wọn sì kọ ọ́ sílẹ̀ láti ẹnu Ànábí alápọ̀n-ọ́nlé, Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –,ẹni tí Ọlọ́hun fi ránṣẹ́ sí, tí kò le fi kún un, tí kò le dín in kù. Àwọn Mùsùlùmí pẹ̀lú bí ìlànà ẹ̀kọ́ ẹ̀sìn wọn àti ìwòye wọn ṣe yàtọ̀ sí ara wọn, wọn kò yapa ẹnu nípa gbólóhùn kan ṣoṣo nínú rẹ̀.

Dájúdájú ṣíṣọ́ *Al-Qur'ān* àti gbígbà á wá, láti ìran déran, ti pé, láti ìgbà dégbà, pẹ̀lú àwọn ipò díde nǹkan mọ́lẹ̀ tí ó ga jùlọ àti yíyanrranntí àti mímọ́yán lórí níbi kíkọ ọ́, àti àwọn ọ̀nà tí à ń gbà pè é àti kíké e, àti híhá a sínú àwọn igbá-àyà, àti àwọn ọ̀nà tí wọ́n gbà kọ ọ́ àti àkọtọ́ rẹ̀ sínú àwọn tákàdá, háràfí kankan kò le dínkù nínú rẹ̀, ẹ̀wọ́ kankan kò sì lékún nínú rẹ̀. Ó rọrún fún ẹnikẹ́ni nínú ènìyàn láti ra àtẹ̀jáde kan nínú rẹ̀, ní ayé òde-òní, láti ibi tí ó jìnnà jùlọ ní ìlú Ṣīn *(China)*, tàbí ní ààrin gùngùn àwọn orílẹ̀-èdè Áfíríkà, kí ó le ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀ pẹ̀lú àwọn àkọsílẹ̀ *Al-Qur'ān*, èyí tí wọ́n ti kọ síwájú ẹgbẹ̀rún ọdún sí àsìkò yìí, tí àwọn ilé-ọnà kárí ayé sì tọ́jú rẹ̀ pamọ́, kí ó le ṣàwárí pàápàá tí ó ṣe ènìyàn ní èǹmọ̀, àti pé ọ̀nà tí à ń gbà pe àwọn háràfí rẹ̀, àwọn gbólóhùn rẹ̀ àti àwọn òfin kíké e, bákan náà ní ó ti wà, kò yípadà, wọn kò sì pààrọ̀ rẹ̀, pẹ̀lú bí àsìkò ti ń yàtọ̀ sí ara wọn, tí àwọn èdè sì jẹ́ ọlọ́kan-ò-jọ̀kan, bóyá o gbọ́ ọ láti ẹnu ọmọdé kan tí ó ń ké e láti orí, ní ìlú Indūnīsīyā ní ayé òde-òní, tàbí àlùfáà Mùsùlùmí kan, tí ó ń kọ́ àwọn ènìyàn nípa rẹ̀ ní ìlú Makkah, síwájú ẹgbẹ̀rún ọdún sí àsìkò yìí.. Dájúdájú ó wá nínú *Al-Qur'ān* pé: **"Àti pé ìbáṣe pé ọ̀dọ̀ ẹlòmíràn yàtọ̀ sí Ọlọ́hun ni ó ti wá ni, dájúdájú wọn ì bá ti rí ìyapa tí ó pọ̀ nínú rẹ̀"** (*An-Nisā'*: 82). Èyí kì í ṣe ohun ìyanu, nítorí pé dájúdájú Ọlọ́hun, fún ara Rẹ̀ tí mójútó ṣíṣọ́ ọ. Ó sọ wí pé: **"Dájúdájú Àwa ni A sọ Ìrántí (*Al-Qur'ān*) kalẹ̀, àti pé dájúdájú Àwa náà ni A ó ṣọ́ ọ"** (*Al-Ḥijr*:19).



## Ìkánilagara ti àlàyé àti ẹ̀mí:

Ẹni tó ń ka *Al-Qur'ān*, pẹ̀lú àfọkànsí, yóò rí i dájú pé, dájúdájú *Al-Qur'ān* máa ń da ojú ọ̀rọ̀ kọ ẹni tó ń kà á tààràtà, ó sì máa ń bá òun gan-an alára sọ̀rọ̀, kò sì dáwọ́ dúró láti máa bá a fi ọ̀rọ̀ jomitoro ọ̀rọ̀ àti láti máa dojú ọ̀rọ̀ kọ ọ́.. Ohun tó ya ènìyàn lẹ́nu ju iyẹn lọ ni pé, dájúdájú yóò máa síwàjú rẹ̀ sọ àwọn ìrorí rẹ̀, yóò sì máa ṣàlàyé rẹ̀, bíi ẹni pè ó ń kà á síwájú kí ó tó bá ẹ̀mí ara rẹ̀ sọ̀rọ̀  nípa rẹ̀.

Pẹ̀lú pé dájúdájú ayàwòrán lè lágbára láti ya ojú ní ọ̀nà tí yóò fi hàn bíi ẹni ó ń tẹ̀lé ẹni tó ń wòran kiri gbogbo ibi tó bá lọ, ṣùgbọ́n báwo ni ó ṣe rọrùn fún ìwé kan kí ó tẹ̀lé àwọn ìrorí ẹni tó ń kà á, kí ó sì máa mọ ohun tó le jẹ́, kí ó sì máa fèsì sí àwọn ìbéèrè rẹ̀ síwájú kí ó tó sọ ọ́ ní ìgbà mìíràn, pẹ̀lú bí ó ti jẹ́ àwọn tó ń kà á yàtọ̀ sí ara wọn, tí ọ̀làjú wọn kò bá ara wọn mu àti àwọn ìṣesí ìṣẹ̀mí-ayé wọn.

Dájúdájú *Al-Qur'ān* ní ìlànà yìí, èyí tó jọ ènìyàn lójú nípa ṣíṣe àfihàn àwọn ohun tó ń gbé ènìyàn lọ́kàn, àti ṣíṣí aṣọ lójú àwọn àṣírí rẹ̀, àti ṣíṣe àlàyé jíjẹ́ ọ̀lẹ rẹ̀, nínú ohun tó le hàn bíi líle koko ní àkọ́kọ́ ìgbà. Ṣùgbọ́n tí kó jẹ́ nǹkankan àyàfi pé ó ń ta ẹ̀mí jí sí pé kí ó bi làákàyè àti ọkàn lápapọ̀ ní àwọn ìbéèrè, èyí tí ó ti ń lọ́ra fún ìgbà pípẹ́, tí ó sì ǹ sá fún fífèsì sí i..

Nígbà tí ẹnìkan nínú wa bá ń ka *Al-Qur'ān,* tí ó sì ń rí ìtàn àwọn ìjọ kan nínú àwọn ènìyàn àti ìròyìn wọn, tó sì ń ṣẹ̀mí pẹ̀lú àwọn àṣírí ìrorí wọn àti àwọn ohun tó wà ní ẹ̀mí wọn àti àwọn ìgbésẹ̀ wọn àti sísọnù apákan wọn àti lílà àwọn mìíràn.. Yóò kó ẹ̀mí ara rẹ̀ ró, fún ìgbà díẹ̀, yóò gbìyànjú láti tún àwọn èròńgbà rẹ̀ gbé yẹ̀wò.. Ṣùgbọ́n kò jẹ́ nǹkankan àyàfi kí àwọn *āyah* yìí, àwọn àwòrán náà àti àwọn àpèjúwe yìí máa wá ní ọlọ́kan-ò-jọ̀kan, yóò sì máa tẹ̀ síwájú pẹ̀lú wíwọra tí yóò máa súnmọ́ ẹ̀mí díẹ̀ díẹ̀ láìní fura mọ́, títí tí *Al-Qur'ān* yóò fi di dígí fún ẹ̀mí, tí yóò máa ṣe àfihàn pàápàá rẹ̀.. àwọn àléébù rẹ̀, àbùjẹ́kù rẹ̀, àwọn ohun tó ní ìkápá lórí rẹ̀ àti àwọn ìgbàláàyè tó wà fún un... Yóò sì máa wọ ẹ̀mí ẹni tó ń kà á pẹ̀lú jíjinlẹ̀, nítorí kí ó le fà á kalẹ̀ pẹ̀lú gbígbàfà àti fífi rinlẹ̀ pé dájúdájú kò sí ọlọ́hun kankan tó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn àyàfi Ọlọ́hun Allāh nìkan.

Wàá rí i, nígbà tí ìjákàn àti ìsọ̀rètínù, bá wá sí ọkàn rẹ̀, tí yóò máa ka: **"Wí pé: Ẹ̀yin ẹrúsìn Mi, àwọn ẹni tí wọn ṣe aṣeju lórí ẹ̀mí ara wọn! Ẹ ma ṣe jakan kúrò nibi Àánú Ọlọ́hun. Dájúdájú Ọlọ́hun máa n ṣe aforijin gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ tan patapata. Dájúdájú Òun gan-an ni Ọlọ́pọ̀lọpọ̀ Aforijin, Ọlọ́pọ̀lọpọ̀ Àánú"** (*Az-Zumar:* 53).

Nígbà tí nǹkan bá dàrú mọ́ ènìyàn lójú, tí nǹkankan tí ó ní agbára sì ń bá ọkàn rẹ̀ jà, tí ó sì ń wá ẹni tí yóò gbára lé, tí yóò sì sádi, yóò rí àánú níbi ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun tí Ó sọ pé: **"Àti pé ti àwọn ẹrúsìn Mi bá bi ọ́ ní ìbéèrè nípa Mi, dájúdájú Èmi súnmọ́, mo máa ń dáhùn ìpe olùpèpè nígbà tí ó ba pè Mí. Kí wọ́n yáa dáhùn ìpè Mi, kí wọ́n sì gbà Mí gbọ́, kí wọn o le baà mọ̀nà"** (*Al-Baqarah*: 186).




Nígbà tí ènìyàn bá ń ronú pé ìṣẹ̀mí-ayé òun kò gúnrégé mọ́, tí kò sì lágbára láti mú un mọ́ra tàbí kò ní ìkàpá lórí àwọn ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ sí i nínú rẹ̀, yóò rí òògùn tí yóò wò ó sàn, yóò sì rí olùrànlọ́wọ́ tí yóò kún un lọ́wọ́ nínú ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun tí Ó sọ, nínú *Al-Qur'ān*, pé: **"Ọlọ́hun kò la nǹkankan kọ́ ẹ̀mí kan lọ́run àyàfi ohun tí ipá rẹ̀ ká, yóò gba ẹ̀san oore (dáadáa) tí ó ṣe, yóò sì gba (ẹ̀ṣẹ̀) nǹkan (burúkú) tí ó ṣe. Ọlọ́hun Ọba wa! Má ṣe gbá wa mú (pẹ̀lú ìyà) tí a bá gbàgbé, tàbí a ṣe àṣìṣe. Ọlọ́hun Ọba wa! Má ṣe gbé nǹkan tí o le kọ́ wa lọ́rùn gẹ́gẹ́ bí Ó ti gbé e kọ́ àwọn ẹni tí ó síwájú wa lọ́rùn (kódà kí á ní agbára rẹ̀). Má sì ṣe gbérù wá; ohun tí a kò ní agbára rẹ̀. Àti pé ṣe àmójúkúrò fún wa, sì tún ṣe àforíjìn fún wa, kí O sì kẹ́ wa, Ìwọ ni Olugbọ́wọ́ wa, yáa ṣe ìrànlọ́wọ́ fún wa lórí àwọn aláìgbàgbọ́ ènìyàn"** (*Al-Baqarah*: 286).

Will Durant,  tí ó jẹ́ ẹni tí ó pàtàkì jùlọ nínú àwọn òǹkọ̀wé nípa ìtàn ọ̀làjú, níti pàápàá, jẹ́rìí sí ipa *Al-Qur'ān* àti ipò rẹ̀ láàrin gbogbo àwọn onídéédé (*Qiṣṣatul-Ḥaḍārah* {ìtàn ọ̀làjú} 13/78-69), ó sọ wí pé:

Will Durant sọ wí pé:

"Dájúdájú ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn onímímọ̀ àti ìrorí gba *Al-Qur'ān* gbọ́, pẹ̀lú bí ìpín wọn nínú làákàyè àti ìrorí ṣe yapa ara wọn. Èyí kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe nítorí pé ó dé pẹ̀lú àdìsọ́kàn òdodo, èyí tí ó fojú hàn, tí ó sì jẹ́ àtẹ́wọ́gbà fún gbogbo ẹ̀dá... Àdìsọ́kàn tí ó rọrùn jùlọ, tí ó sì kéré jùlọ níbi kí nǹkan takókó".

"Dájúdájú ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn onímímọ̀ àti ìrorí gba Al-Qur'ān gbọ́, pẹ̀lú bí ìpín wọn nínú làákàyè àti ìrorí ṣe yapa ara wọn. Èyí kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe nítorí pé ó dé pẹ̀lú àdìsọ́kàn òdodo, èyí tí ó fojú hàn, tí ó sì jẹ́ àtẹ́wọ́gbà fún gbogbo ẹ̀dá... Àdìsọ́kàn tí ó rọrùn jùlọ, tí ó sì kéré jùlọ níbi kí nǹkan takókó, tó sì jìnnà jùlọ sí àwọn ìlànà àti ètò ìjọsìn àtijọ́, tí ó sì ní òmìnira jùlọ kúrò níbi ṣíṣe ẹbọ àti jíjẹ́ alàgbà… Dájúdájú ẹ̀sìn Islām ti kọ́ àwọn ènìyàn pé kí wọ́n dojú kọ ìlekoko ìṣẹ̀mí-ayé, kí wọ́n sì fi ara da àwọn àjàgà rẹ̀, láìfi igbe ta, láìsi jẹ́ kó sú wọn... Dájúdájú  ó sọ oríkì ohun tó ń jẹ́ ẹ̀sìn, ó sì fi ààlà sí i, ẹlẹ́sìn Kìrìsìtẹ́nì àti ẹlẹ́sìn Yahūd, èyí tí àdìsọ́kàn rẹ̀ ní àlááfíà, kò ní rí ohun tí yóò kọ̀ fún un láti gbà á". **{Kì í ṣe dáadáa ni kí ẹ máa da ojú yín kọ ibùyọ tàbí ibùwọ̀ oòrùn, ṣùgbọ́n dáadáa ni  ẹni tí ó ba ní ìgbàgbọ́ pẹ̀lú Ọlọ́hun, àti Ọjọ́ ìkẹ́yìn, àti àwọn *Malā'ikah* àti Tírà, àti àwọn Òjíṣẹ́, tí ó si tún ná owó pẹ̀lú ìfẹ́ ti ẹ̀ náà fún un, fún àwọn alásúnmọ́, àti àwọn ọmọ òrukàn, àti àwọn aláìní, àti ọmọ oju ọ̀nà (arìnrìn-àjò tí nǹkan tán mọ́ lọ́wọ́ níbi tí kì í ṣe ìlú rẹ̀), àti àwọn tí wọ́n ń tọrọ àti láti bọ́kun ẹrú, tí ó sì ń gbé ìrun nàró, tí ó sì ń yọ ọrẹ àánú ọ̀ranyàn (*Zakāh*), àti àwọn tí wọ́n máa ń pé àdéhùn wọn nígbà tí wọ́n bá ṣe àdéhùn, àti àwọn tí wọ́n máa ń ṣe sùúrù nígbà òsì, àìsàn àti ní àsìkò ogun. Àwọn wọ̀nyẹn ni wọ́n sọ òdodo (níbi ìgbàgbọ́ wọn), àwọn wọ̀nyẹn sì ni olubẹ̀rù Ọlọ́hun}**. " (*Al-Baqarah*: 177).



# Níbo ni *Al-Qur'ān* ti wá?

## Ìbéèrè

Ìbéèrè tó mú ọgbọ́n lọ́wọ́, èyí tó máa ń yára jẹyọ nígbà tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìwé mímọ́ àwọn Mùsùlùmí: *Al-Qur'ān*, àti Ànábì Muḥammad – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a –. Kílódé tí ó jẹ́ dandan fún wa láti gba ẹ̀gbàwá àwọn Mùsùlùmí nípa ìtàn yìí? Ṣé kò tọ́ fún wa kí á mú àwọn ìbéèrè wá lórí rẹ̀?

Àwọn àkọ̀tàn kò yapa ẹnu nípa pé dájúdájú *Al-Qur'ān* dé lórí ahọ́n ọkùnrin Lárúbáwá kan, èyí tí kò le kà, tí kò sì le kọ. Wọ́n bíi ní ní ìlú *Makkah* ní ọgọ́rùn-ún ọdún kẹfà lẹ́yìn bíbí Ànábì 'Īsā. Orúkọ rẹ̀ Muḥammad ọmọ 'Abdil-Lāh.. Ìjẹ́ríí ìtàn-ayé, èyí tí ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ àkọ̀tàn mú wá, kò sí ìjẹ́ríí kankan tó jọ ọ́. Gẹ́gẹ́ bí a ti ń kà á nínú Tírà yìí pé kì í ṣe ara iṣẹ́ ẹni tó mú un wá, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ọ̀rọ̀ alápọ̀n-ọ́nlé, èyí tí wọ́n fi ránṣẹ́ sí i láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun. Iṣẹ́ Ànábì Muḥammad kò ju kí ó mú un dé ògóngó lọ, kí ó sì ṣàlàyé rẹ̀ fún àwọn ènìyàn láìsí àfikún, tí kò sì sí àdínkù.

Ṣé ó ṣeéṣe kí ó jẹ́ wí pé Ànábì Muḥammad, Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn *Islām* rán, níti pàápàá, ṣe àgbélẹ̀rọ̀ rẹ̀ láti ọ̀dọ̀ ẹ̀mí ara rẹ̀, tàbí ó kọ́ ohun tí ń bẹ nínú rẹ̀, ò sì tún àgbékalẹ̀ rẹ̀ rọ, ó sì mú un wá bá àwọn ènìyàn lẹ́yàn náà?

> Tí ó bá jẹ́ wí pé Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn *Islām* rán fẹ́ déte láti tan lílapa rẹ̀ lórí àwọn ènìyàn ká, pẹ̀lú ṣíṣe àfitì àwọn ọ̀rọ̀ rẹ̀ sí Ọlọ́hun ni, kín ni ó wá dé tí kò fi pàpèmọ́ra pé dájúdájú gbogbo ọ̀rọ̀ òun, ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun ni ó ti wá?!

Èyí jẹ́ àwọn ìbéèrè tó bá òfin ẹ̀sìn *Islām* mu, ó máa ń de làákàyè lẹ́ẹ̀kan náà, nígbà tí ẹni náà kò bá ka *Al-Qur'ān* rí, tí kò kọ́ ọ rí, tàbí kò jẹ́ onímímọ̀ nípa ìtàn àti ìgbésí-ayé Ànábì Muḥammad.

Ohun tí a mọ̀, tí àwọn ẹ̀kọ́ ìtàn-ayé sì fi ẹsẹ̀ rẹ̀ rinlẹ̀ ni pé dájúdájú ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n àti àwọn aláròjinlẹ̀ máa ń ja lu àwọn iṣẹ́ ẹni tó yàtọ̀ sí wọn, wọn yóò jí i dàkọ, wọn yóò sì fi tì sí ara wọn, kín ni ó wá dé tí ẹnikan yóò wá fi iṣẹ́ àìrójú làákàyè rẹ̀ tí sí ẹlòmíràn?

Nínú ohun tí ó pè fún àkíyèsí ni pé dájúdájú tí ó bá jẹ́ pé, ó fẹ́ déte láti tan lílapa rẹ̀ lórí àwọn ènìyàn ká, pẹ̀lú ṣíṣe àfitì rẹ̀ sí Ọlọ́hun ni, kín ni ó wá dé tí kò fi pàpèmọ́ra pé dájúdájú gbogbo ọ̀rọ̀ òun, ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun ni ó ti wá?!

Ṣé ó bá làákàyè mu, kí á ní wí pé òun ni ẹni tó kọ́ Tírà yìí jọ, tí ó sì ṣe àgbélẹ̀rọ rẹ̀, ó kàn fẹ́ fi bí ó ṣe fi tì sí Ọlọ́hun jẹ́ kí lílapa rẹ̀ gbilẹ̀, àti láti gbé ipò àti iyì rẹ̀ ga. Ní ìgbà tó jẹ́ wí pé, à ń rí nínú Tírà yìí kan náà; àwọn ààyè tó pọ̀, pé Ẹni tó ń sọ̀rọ̀ ń bá Ànábì Muḥammad wí, ní ìbáwí sàn-án, yóò sì máa dojú ìmọ̀ràn kọ ọ́, àti àtúnṣe sí àwọn àṣìṣe rẹ̀?

Dájúdájú *Al-Qur'ān* – gẹ́gẹ́ bí ẹni tó bá kà á yóò ti mọ̀ – kò ṣe àyàfi, nínú bíbá a wí, agbegbe kan pàtó tàbí lápapọ̀. Dájúdájú ó bá Ànábì Muḥammad wí níbi àwọn ọ̀ràn ìṣẹ̀mí-ayé rẹ̀, èyí tó ní í ṣe pẹ̀lú ẹbí rẹ̀. Bẹ́ẹ̀ náà ni ó tún ka apákan nínú àwọn ìgbésẹ̀ rẹ̀ níbi dídarí sí àṣìṣe, kódà títí kan ọ̀nà tó ń gbà pe àwọn ènìyàn sí ẹ̀sìn Ọlọ́hun!

Nínú èyí ni pé, dájúdájú ọkùnrin afọ́jú kan nínú àwọn sàábé Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wá bá Ànábì, ó sì ti wà nínú àìrójú pẹ̀lú pípe ọ̀kan nínú àwọn abẹnugan iran *Quraysh*, ó ń rankàn pé kó gba ẹ̀sìn *Islām*, afọ́jú náà kò mọ̀ pé Ànábì Muḥammad wà nínú àìrójú pẹ̀lú èyí, ó sì pè é pé: Kọ́ mi nínú ohun tí Ọlọ́hun fi mọ̀ ọ́, ó sí ran kankan mọ́ ọn, ó sì pàarà gbólóhùn rẹ̀ yìí, nítorí náà ó fa ojú ro (ìrísí ojú rẹ̀ yí padà látara ìbínú). Ó fẹ́ kí afọ́jú yìí kóra ró títí tí yóò fi parí ohun tó ń ṣe lọ́wọ́, lẹ́yìn náà Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – yí kúrò lọ́dọ̀ afọ́jú yìí, kò sì dá a lóhùn. *Al-Qur'ān* de àsìkò tí ìṣẹ̀lẹ̀ yìí wáyé, ó sì fi rinlẹ̀ sínú ìtàn-ayé. Ó sì ṣàlàyé ìṣẹ̀lẹ̀ yìí ní ọ̀nà tó mọ́yán lórí, pẹ̀lú ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé, pẹ̀lú àlàyé bí Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – ti fajú ro níwájú afọ́jú yìí, àti bí ó ti pa á tì láìfún un ní èsì. *Al-Qur'ān* kò tún dúró níbí, ṣùgbọ́n ó fi bíbú Ànábì Ọlọ́hun tẹ̀lé e àti ìkìlọ̀ tó lọ sàn án, tó lágbára pé irú rẹ̀ kò gbọdọ̀ wáyé mọ́, nínú Sūrah (ọgbà-ọ̀rọ̀ *Al-Qur'ān*), èyí tí wọ́n sọ ní orúkọ tí ó ń fi ìdí ìṣẹ̀lẹ̀ yìí múlẹ̀. **"Ó fa oju ro, o si pẹyinda. Nítorí pé afọ́jú wa ba a. Ṣùgbọ́n kin ni yóò fi mọ ọ pe bóyá yóò di ẹni mímọ́? Tàbí ki o gba irántí, ti irántí náà yóò si ṣe e ni anfaani. Ni ti ẹni tí ó ro pe oun ti rọrọ tan. Òun ni iwọ n tẹti sílẹ̀ fún. Àti pé kò sí (ẹ̀ṣẹ̀ kankan) lórí rẹ, ti ko ba fọ ara rẹ mọ. Ṣùgbọ́n ẹni tí ó ba wa ba ọ ti n posẹṣẹ. Ti òun sì ń bẹ̀rù (Ọlọ́hun). Òun ni iwọ n pa a ti. Bẹ́ẹ̀ko, dájúdájú (*Al-Qur'ān*) jẹ irántí"**. Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun máa sọ fún afọ́jú yìí, lẹ́yìn ìṣẹ̀lẹ̀ yìí, ní ìgbà tó bá dé pé: "Mo kí ẹni tí Ọlọ́hun Ọba mi bá mi wí nítorí rẹ̀ káàbọ̀". Ó sì máa ń tẹ́ aṣọ rẹ̀ sílẹ̀ fún un.

Dájúdájú *Al-Qur'ān* fi rinlẹ̀ fún wa; ọlọ́kan-ò-jọ̀kan nínú àwọn ìtàn ìdánilẹ́kọ̀, àti àwọn ìbáwí fún Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, pẹ̀lú ohun tí yóò ni ẹnikẹ́ni nínú wa lára, nígbàn mìíràn, kí wọ́n sọ irú rẹ̀ sí i láàrin àwọn ènìyàn.. Ṣé ẹnikankan le máa fọ́n àwọn àṣìṣe rẹ̀ ká, tí yóò sì fi rinlẹ̀ sínú ìwé ìtàn, ní irú ọ̀nà yìí, tí ó bá jẹ́ wí pé ó ń wá ipò àti iyì fún ara rẹ̀ ni!

Lẹ́yìn náà, èyí ni ìtàn-ayé, ó fi ń rinlẹ̀ fún wa, ní ọlọ́kan-ò-jọ̀kan ààyè, bí Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – ti ṣẹ̀mí ní àwọn àsìkò tó le koko, tó ń rankàn, nínú rẹ̀ pé kí iṣẹ́-ìránṣẹ́ sọ̀kalẹ̀, láti fi òdodo rẹ̀ àti ipò rinlẹ̀, tàbí bíbọ́pá-bọ́ṣẹ̀ rẹ̀ àti bíbọ́pá-bọ́ṣẹ̀ àwọn ara ilé rẹ̀, tí kò sì ní wá bá a..

> Dájúdájú *Al-Qur'ān* fi rinlẹ̀ fún wa; ọlọ́kan-ò-jọ̀kan nínú àwọn ìtàn ìdánilẹ́kọ̀, àti àwọn ìbáwí fún Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, pẹ̀lú ohun tí yóò ni ẹnikẹ́ni nínú wa lára, nígbà mìíràn, kí wọ́n sọ irú rẹ̀ sí i láàrin àwọn ènìyàn.

Nínú èyí ni pé dájúdájú àwọn ìjọ rẹ̀, tí wọ́n bá a ṣe ọ̀tà, tí wọ́n fi ṣùtá kàn án, wọ́n wá ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú apákan àwọn onímímọ̀ àti Tírà, nínú àwọn ìjọ tó ti síwájú, láti wá ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú wọn láti gbógun ti Ànábì Muḥammad.

Nítorí náà wọ́n fún wọn ní ìmọ̀ràn pé kí wọ́n bi í ní ìbéèrè mẹ́ta, tí ó bá da yín lóhùn, a jẹ́ wí pé Ànábì ni. Ṣùgbọ́n tí kò bá da yín lóhùn, a jẹ́ wí pé kì í ṣe Ànábì.. Wọ́n ṣe bẹ́ẹ̀, wọ́n sì bi í léèrè, Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – sì sọ fún wọn, ní ẹni tó ń pè wọ́n níjà pé: Màá da yín lóhùn ní ọ̀la..

Iṣẹ́-ìránṣẹ́ dáwọ́ dúrú fún Ànábì Muḥammad, fún àwọn ọjọ́ díẹ̀, kò wá bá a, àwọn ọ̀tá rẹ̀ bẹ̀rẹ̀ sí ní rékọjá pẹ̀lú rẹ̀, wọ́n sì ń fi í ṣe yẹ̀yẹ̀, nítorí pé kò fèsì sí ìbéèrè wọn. Ìbànújẹ́ tó le koko bá Ànábì Muḥammad nítorí ìṣẹ̀lẹ̀ yìí. Síbẹ̀ iṣẹ́-ìránṣẹ́ kò sọ̀kalẹ̀ fún un àyàfi lẹ́yìn ọjọ́ mẹ́ẹ̀dógún láti fèsì sí àwọn ìbéèrè yìí, pẹ̀lú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ *Al-Qur'ān* fún Ànábì Muḥammad pé: "Má sọ pọ̀ún pé; máa ṣe iyẹn ní ọ̀la, àyàfi tí o bá ti so ó mọ́ Èròngbà Ọlọ́hun, tí ó sì wí pé: Tí Ọlọ́hun bá fẹ́. Àti pé dájúdájú lílọ́ èsì rẹ lára yìí jẹ́ ẹ̀kọ́ fún ẹ láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun. **"Àyàfi (pẹ̀lú) ti Ọlọ́hun ba fẹ. Ki o si ránti Ọlọ́hun Ọba rẹ nígbà tí o ba gbagbe, si wí pé: O ṣeeṣe ki Ọlọ́hun Ọba mi fi mi mọ̀nà si eléyìí tí ó súnmọ́ jùlọ si ìyẹn ni ìtọ́nisọ́nà"** (*Al-Kahf*: 24).



## Àwọn fífi ẹ̀sùn kanni léraléra:

Nínú ohun tó ya ènìyàn lẹ́nu ni pé dájúdájú, ìtàn Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – àti ìṣẹ̀mí-ayé rẹ̀, a lè kà á sí ara àwọn ẹ̀rí tó hàn júlọ lórí jíjẹ́ olódodo rẹ̀..

Báwo ni ọkùnrin kan tó jẹ́ wí pé òpè ni, tí kò mọ̀ ọ́n kọ, kò mọ̀ ọ́n kà, tó ń gbé láàrin àwọn òpè ènìyàn, tó ń bá wọn gbé irú ìṣẹ̀mí-ayé wọn, tó máa ń wà níbi àwọn ibùjokòó wọn – tí kò sí ìwà pòkíì níbẹ̀ – tó gba àìrójú pẹ̀lú ìjẹ-ìmu ara rẹ̀ àti àwọn ara ilé rẹ̀, tó ń da ẹran jẹ̀ lórí owó-ọ̀yà tàbí tó jẹ́ òǹṣòwò pẹ̀lú owó-iṣẹ́, tí kò ní àjọṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn onímímọ̀, ó lo ohun tó pọ̀ júlọ nínú ìṣẹ̀mí-ayé rẹ̀ lórí èyí, ogójì ọdún tó pé pérépéré. Ní ẹ̀ẹ̀kan náà, ó bẹ̀rẹ̀ sí ní máa bá wọn sọ ohun tí wọn kò mọ irú rẹ̀ tẹ́lẹ̀, pẹ̀lú ohun tí wọn kò mọ̀ láti ọ̀dọ̀ àwọn bàbá wọn. Ó fún wọn ní ìró nípa ìtàn àwọn àkọ́kọ́, àti ìtàn bí dídá ẹ̀dá ti bẹ̀rẹ̀, àti àlàyé ìṣẹ̀mí-ayé àwọn Ànábì tí ó ti síwájú, àti àwọn ohun tó bùkáátà sí ìwòye tó yè kooro nínú àwọn òfin ìdájọ́ níbi gbogbo agbegbe ìṣẹ̀mí-ayé!..

Dájúdájú pàápàá yìí kó ìnira bá àwọn ọ̀tá Ànábì Muḥammad, nínú àwọn ìjọ rẹ̀ lápapọ̀, nítorí náà dàrúdàpọ̀ bá wọn nípa àlàyé ohun tó mú wá, nítorí náà wọ́n wò ó pé ẹ̀sùn wo ni ó le tà láti wá àwọn ènìyàn ní ìṣọ́ra nípa rẹ̀?

Nínú ohun tó ṣòro ni kí á lérò pé *Al-Qur'ān* jẹ́ àgbélẹ̀rọ̀ Ànábì Muḥammad, èyí kò le bá làákàyè mu ní ọ̀dọ̀ ẹni tó bá ka *Al-Qur'ān*, tó sì ronú sí i. Kò sì rọrùn kó kọ́ ọ láti ọ̀dọ̀ ẹlòmíràn yàtọ̀ sí i, àárin wa ni ó ń gbé, a sì mọ àtúpalẹ̀ ìṣẹ̀mí-ayé rẹ̀, nítorí náà wọ́n fi ẹ̀sùn nǹkan àti ìdàkejì rẹ̀ kàn án. Nígbà kan wọ́n wí pé; ó gbà á lọ́wọ́ àwọn tó síwájú rẹ̀ ni, nígbà mìíràn, wọ́n wí pé; ó dá àdáparọ̀ rẹ̀ láti ọ̀dọ̀ ara rẹ̀ ni, nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, wọ́n wí pé; àlá tó lá lójú oorun ni ó ń rọ́… nígbà tí wọ́n kágara láti fi èyí rinlẹ̀, wọ́n wí pé; òpìdán, tàbí akọrin, tàbí kò jẹ́ wèrè.


Gbogbo èyí jẹ́ àwáwí kan náà pẹ̀lú yíyàtọ̀ orúkọ lásán... ṣé wọn kò dá àdáparọ̀ idán mọ́ Mūsā – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –? Ṣé wọn kò pe ʻĪsā – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – ní wèrè?

Bàyìí náà ni ọ̀ràn ti rí, pẹ̀lú gbogbo àwọn Ànábì tó ti síwájú – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá wọn –, nígbà tí àwọn ọ̀tá wọn kò bá rí ẹ̀sùn tí wọ́n le fi kàn wọ́n, wọn yóò máa pè wọ́n ni òpìdán tàbí wèrè. Bàyìí ni ìṣesí ajẹ́rìí èké, tó bá kẹ́fìn pé ipò tí òun wà wọ́, pé ẹ̀rí òun ti di òbu, gbogbo ààyè ni yóò dojú kọ, gbogbo ẹ̀sùn àbùkù ni yóò fi kan èèyàn, bóyá ó le rí ààyè kan dúró sí, ṣùgbọ́n báwo ni yóò ti rí èyí ṣe.

> Bàyìí náà ni ọ̀ràn ti rí, pẹ̀lú gbogbo àwọn Ànábì tí ó ti síwájú – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá wọn – , nígbà tí àwọn ọ̀tá wọn kò bá rí ẹ̀sùn tí wọ́n le fi kàn wọ́n, wọn yóò máa pè wọ́n ni òpìdán tàbí were.

## Kílódé tí a kò kà á sí jíjẹ́ akin lásán:

Gbogbo kálukú ni ó fi ẹnu kò pé dájúdájú Ọlọ́hun fi sínú làákàyè ènìyàn; àwọn ìkápá àti agbára ọ̀tun, èyí tó ṣòro láti ronú kàn. Ṣùgbọ́n ṣé kì í ṣe ìpilẹ̀ ni pé làákàyè gbọdọ̀ ní ààlà níbi àwárí rẹ̀ àti àgbọ́yé rẹ̀.. Pẹ̀lú pé làákàyè jẹ́rìí sí bíbẹ Ọlọ́hun Ọba, Adẹ́dàá, Alágbara, àti wí pé jíjẹ́ Onídéédé Ọlọ́hun Ọba yìí sọ ọ́ di dandan pé ìṣẹ̀mí mìíràn gbọdọ̀ wà, tí gbogbo kálukú yóò gba ẹ̀san rẹ̀ níbẹ̀, bóyá rere ni tàbí aburú. Ṣùgbọ́n ṣé làákàyè lágbára láti fi àwọn ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé àti àwọn ohun tó gba ọgbọ́n mìíràn rinlẹ̀,, nínú ohun tí kò sí àwọn ẹ̀rí tàbí ohun tó le gbè é lẹ́sẹ̀ fún.



Ẹni tó ń ka *Al-Qur'ān*, yóò rí i pé dájúdájú ó ń ṣàlàyé ohun tó ń jẹ́ ìgbàgbọ́ òdodo fún wa ní ẹ̀kùnrẹ́rẹ́, ó sì ń ṣàlàyé fún wa ní ẹ̀kùnrẹ́rẹ́ tó mọ́yán lórí nípa bíbẹ̀rẹ̀ ìṣẹ̀dá, bí yóò ti parí, ó ń ròyìn ọgbà-ìdẹ̀ra *Al-Jannah* àti ìdẹ̀ra rẹ̀, àti iná àti ìyà rẹ̀, iye òǹkà àwọn ìlẹ̀kùn rẹ̀, òǹkà àwọn *Malā'ikah* tí wọ́n gbé ṣíṣọ́ ọ kọ́ lọ́rùn. Ó tún ń ṣàlàyé àwọn ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé nípa pàápàá ilé-ayé àti ènìyàn.. nítorí náà ìwòye làákàyè wo ni wọ́n mọ gbogbo àlàyé wọ̀nyí lé.

Dájúdájú èyí kò le wáyé láti ìpasẹ̀ làákàyè àti jíjẹ́ akin, nítorí náà nínú kó jẹ́ iró, ìbàjẹ́ àti èròkerò tàbí kó jẹ́ òdodo tí a kò le mọ̀ àyàfi pẹ̀lú kíkọ́ ọ àti pípè é fún ènìyàn.


Dájúdájú a ti rí i pé ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ ayé òde-òní fi apákan nínú àwọn pàápàá rẹ̀ rinlẹ̀, nígbà tó jẹ́ wí pé kò tako nǹkankan nínú àwọn ẹ̀kọ́ rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí o ti jẹ́ wí pé ó bá ohun tó wà nínú àwọn Tírà tó sọkalẹ̀ láti sánmà tó ti síwájú mu níbi àwọn ìró àwọn ohun ìkọ̀kọ̀.

## Bóyá àwọn ìwé tó tún àgbékalẹ̀ wọn rọ ni:

Ẹ jẹ́ kí á kóra ró láti ronú sí wí pé, ṣé ó ṣeéṣe, kódà ní ọ̀nà kékeré, kí ó jẹ́ wí pé ó fa gbogbo àwọn ìmọ̀ yìí yọ nínú àwọn Tírà tí Ọlọ́hun fún àwọn Ànábì tó síwájú?

Tí a bá kúrò níbi pàápàá pé Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – jẹ́ òpè, kò mọ̀ ọ́n kọ, kò sì mọ̀ ọ́n kà, àti dájúdájú òpè ni àwọn tó pọ̀ júlọ níní àwọn ènìyàn rẹ̀, wọn kò ní ìríri nípa àwọn ìmọ̀ yìí tẹ́lẹ̀, bẹ́ẹ̀ ni kò bá ẹni kankan nínú àwọn oní-Tírà tó síwájú ṣe àṣepọ̀ rí – yàtọ̀ sí ìpàdé ráńpẹ́ kan tó wáyé ní ojú-ọ̀nà, nígbà tó ń ṣe ìrìn-àjò, ní ìgbà kékeré rẹ̀, tí àwọn ẹbí rẹ̀ sì wà níbẹ̀ nígbà náà –, àti pé dájúdájú pàápàá ìtàn-ayé fi rinlẹ̀ pé dájúdájú àwọn onímímọ̀ nípa àwọn Tírà Ọlọ́hun, nígbà náà, máa ń fi ìmọ̀ pamọ́, wọ́n sì máa ń jẹ́ kó wà ní ọ̀dọ̀ àwọn níkan, nítorí àti ṣọ́ ipò wọn, wọn kò jẹ́ kò jẹ́ ohun tó tàn ká, tí wọ́n fi kọ́ àwọn ènìyàn..

Tí a bá kúrò níbi gbogbo èyí tán pátápátá, dájúdájú pàápàá tó ṣe rẹ́gí pẹ̀lú èyí, ní ọ̀dọ̀ gbogbo olùṣe ìwadìí ni pé dájúdájú *Al-Qur'ān* kò gba gbogbo ohun tó wà nínú àwọn Tírà tó sọkalẹ̀ láti sánmà tó ń bẹ ní ìgbà náà, ṣùgbọ́n ó dé láti wá ṣe àtúnṣe apákan àwọn ohun tó jẹ́ àṣìṣe (èyí tí àwọn onímímọ̀ kan nípa ẹ̀sìn yí padà), ó sì wá pé àwọn àbùjẹ́kù tó wà níbi àwọn ìtàn kan, àti láti wá ṣe àfihàn ohun tí wọ́n ń fi pamọ́ nínú ìmọ̀, ó ń ṣàlàyé àwọn àdìsọ́kàn anù tàbí ti ìwà èyí tí apákan àwọn onímímọ̀ ti so mọ́ ẹ̀sìn àwọn Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá wọn –, tí kò sì so mọ́ ọn. *Al-Qur'ān* kún fún àwọn àpèjúwe lórí èyí.. Ṣé ó wá rọrùn, pẹ̀lú èyí, kí ó jẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ fún wọn, kó sì jẹ́ wí pé ó gba àwọn ìmọ̀ yìí ní ọ̀dọ̀ wọn?!



## Pàápàá ìtàn-ayé tó ń ṣe ìyàtọ̀:

Kò le bọ́ mọ́ olùṣewadìí tó jẹ́ onídéédé lọ́wọ́, kí ó kóra ró fún ìgbà pípẹ́ láti ronú.. Ṣé Ìránṣẹ́ tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn *Islām* rán, Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – kì í ṣe ọmọ ìran Lárúbáwá ni?

Ṣé ìtàn kò sọ fún wa pé dájúdájú àwọn ènìyàn rẹ̀, tí wọ́n jẹ́ Lárúbáwá, ní ìgbà náà, kò ní ìmọ̀ kankan tí wọ́n máa ń fi í ṣe fáàrí bíkòṣe dídá láhọ́n àti mímọ ọ̀rọ̀ gbé kalẹ̀? Àti pé dájúdájú iṣẹ́ àkànṣe wọn kò ju orin kíkọ àti mímọ àgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ lọ. Wọ́n máa ń ṣe àgbékalẹ̀ àwọn àpèjọ, ìpàdé àti àjọ̀dún fún un. Ìdílé kan yóò ga, ìdílé mìíràn yóò sì rẹlẹ̀, nítorí orin tí wọ́n kọ nípa rẹ̀!

Àwọn ìwé ìtàn àti ẹ̀kọ́ ń fún wa ní ìró pé dájúdájú ẹnìkankan nínú wọn kò ní kọ orin kan tàbí sọ̀rọ̀ kan àyàfi kí wọ́n rí nǹkan sọ sí i, nítorí náà wọn a pé ohun tó dínkù nínú ọ̀rọ̀ rẹ̀, wọn yóò ṣe àlépabá ohun tó bọ́ mọ́ ọn lọ́wọ́, wọn yóò dá ọ̀rọ̀ rẹ̀ padà sí i lẹ́nu pẹ̀lú ọ̀nà tí òun náà gbà, àti pé èyí ni ìdíje wọn dá lé lórí, òun sì ni ó máa ń ṣe àfihàn agbára wọn àti dídíyàtọ̀ wọn.

Báwo ni ọ̀tá wọn tó le koko jùlọ yóò ṣe dé, ẹni tí wọn kò ní kó nǹkan agbára ogun pamọ́ kí wọ́n tó le jà á lógun, le fi ìyà jẹ ẹ́, tàbí wá àwọn ènìyàn ní ìṣọ́ra nípa rẹ̀, tí yóò sì pè wọ́n níjà pé kí wọ́n mú irú *Al-Qur'ān* yìí wá, tàbí irú ìpín kékeré kan nínú rẹ̀, lẹ́yìn náà tí wọn kò sì le kojú ìpèníjà náà àyàfi pẹ̀lú pípa ẹnu mọ́ àti sísá fún síṣọ irú rẹ̀ kalẹ̀!

Ṣé Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – kò páyà pẹ̀lú ìpeni níjà yìí, pé ó le wú ìlara tó wà ní ọkàn wọn jáde níbi ohun tí wọ́n dá yanranntí níbẹ̀ jùlọ, tí ìmọ̀ wọn nípa rẹ̀ lágbara jùlọ, kí wọ́n jígìrì láti bá a ṣe ìfànfà ní ọ̀kọ̀ọ̀kan tàbí ní àpapọ̀, láti dá a lákẹ́, kí wọ́n sì fi jíjẹ́ ìbàjẹ́ ohun tó mú wá rinlẹ̀ fún àwọn ènìyàn!

Lẹ́yìn náà kí a ti ẹ̀ gbà pé dájúdájú ó ṣe àyà gbàǹgbà lórí èyí, nítorí pé ó ti mọ bí agbára àwọn ènìyàn rẹ̀ ti mọ, báwo wáá ni ó ṣe sọ̀rọ̀ pọ̀nún, tó sì gbé ìdájọ́ rẹ̀ kalẹ̀ lórí àwọn ìran ènìyàn tó ń bọ̀ títí di ọjọ́ Ìgbéǹde pé dájúdájú wọn kò le lágbára láti mú irú rẹ̀ wá, wọ́n kò sì le mú ìpín kan nínú rẹ̀ wá, kódà kí wọ́n parapọ̀ lórí rẹ̀?!

Èyí jẹ́ ìfi ẹ̀mí wéwu, tí ẹnìkankan kò le da àyà kọ ọ́, àyàfi ẹni tí ó bá dáńgájíà, tí ó sì dá ara rẹ̀ lójú lórí ohun tí ó fẹ́ sọ.. Báyìí ni ọ̀ràn rí, ìran Quraysh àti àwọn àgbà-ọ̀jẹ̀ tí wọ́n dá nítọ́, kò ṣe àyà gbàǹgbà láti ṣe àkójọ ọ̀rọ̀ kankan tí yóò dà bíi *Al-Qur'ān,* tàbi àwọn abala kan nínú rẹ̀. Èyí ni pàápàá tí ó ti rékọjá, láti ìgbà náà títí di ayé òde-òní, gbogbo ẹni tí ó gbìyànjú tàbí gbèrò láti ṣe èyí, láti ìgbà dégbà ṣẹ́rí padà pẹ̀lú òfo, èyí tí ó mú àbùkù lọ́wọ́, ó tún di ẹni àmúṣeré láàrin àwọn ènìyàn rẹ̀, ẹni tí ìṣesí rẹ̀ pè fún yẹ̀yẹ́ àti ìyẹpẹrẹ àìní àgbékalẹ̀ ọ̀rọ̀ láàrin wọn.

## *Sūratul-Fātiḥah:*

Òhun ni *Sūrah* (ọgbà-ọ̀rọ̀) tí ó pàtàkì jùlọ nínú *Al-Qur'ān,* Mùsùlùmí máa ń pààrà rẹ̀ ní gbogbo ìgbà lórí ìrun rẹ̀. Ìtumọ̀ rẹ̀, ní ṣókí, ni ń bọ̀ yìí:

### Ìtumọ̀ *Sūratul-Fātiḥah*

| | |
|---|---|
| **{(Mo bẹ̀rẹ̀) pẹ̀lú Orúkọ Ọlọ́hun Allāh, Ọba Àjọkẹ́ Ayé, Ọba Àṣàkẹ́ Ọ̀run}** | Mo bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú Orúkọ Ọlọ́hun níti ẹ̀kọ́ àti gbígbé E tóbi, Òun náà sì ni Ọba tí Ó gba ìròyìn pẹ̀lú ìkẹ́, èyí tí ó kárí gbogbo nǹkan. |
| **{Gbogbo ọpẹ́ (àti ẹyìn) ti Ọlọ́hun ni í ṣe, Ọba Olùtọ́jú gbogbo àgbáyé}** | Mò ń ṣe ẹyìn fún Ọlọ́hun pẹ̀lú gbogbo àwọn Ìròyìn Rẹ̀ àti àwọn ìṣe Rẹ̀, àti àwọn ìdẹ̀ra Rẹ̀, èyí tí ó hàn àti èyí tí ó pamọ́ pẹ̀lú ìfẹ́ àti gbígbé E tóbi. Òun ni Aṣẹ̀dá, Òun ni Ó ni gbogbo nǹkan, Òun ni Olùdarí gbogbo nǹkan, Òun ni Ó ń ṣe ìdẹ̀ra fún àwọn ẹ̀dá. |
| **{Ọba Àjọkẹ́ Ayé, Ọba Àṣàkẹ́ Ọ̀run}** | Ẹni tí Ó gba ìròyìn pẹ̀lú gbogbo àwọn ìtumọ̀ ìkẹ́, àwọn ìṣesí rẹ̀, àti àwọn agbegbe rẹ̀. Òun ni Oníkẹ̀ẹ́ tí ó kárí, èyí tí ó kárí gbogbo nǹkan tí ń bẹ nínú ayé yìí àti ìkẹ́ ẹ̀ṣà, èyí tí ó máa ń dé ọ̀dọ̀ àwọn ẹrúsìn Rẹ̀ olùgbàgbọ́ òdodo. |
| **{Olùkápá Ọjọ́ ẹ̀san}** | Olùkápá àti Olùdarí ní Ọjọ́ ẹ̀san àti ìṣirò-iṣẹ́ |
| **{Ìrẹ nìkan ni àwa yóò máa sìn, ọ̀dọ̀ Rẹ̀ nìkan sì ni àwa yóò máa wá ìrànlọ́wọ́ sí}** | A ó dá Ọ, Ìrẹ Ọlọ́hun Ọba wa, ṣà lẹ́ṣa pẹ̀lú ìjọsìn, a kò ní fi ẹlòmíràn ṣe ẹbọ pẹ̀lú Rẹ níbi èyíkéyìí ìran ìjọsìn, a sì ń wá ìrànlọ́wọ́ ní ọ̀dọ̀ Rẹ nìkan ṣoṣo níbi gbogbo ọ̀ràn wa, Ọwọ́ Rẹ ni gbogbo àṣẹ wà, ẹnìkankan kò ní ohun tí ó mọ bíi ìwọ̀n ọmọ-ináágún nínú rẹ̀. |
| **{Tọ́ wa sí ọ̀nà tí ó tọ́}** | Ìrẹ Ọlọ́hun! Tọ́ka wa, kí Ó sì fi wá mọ̀nà, kí Ó fi wá ṣe kòǹgẹ́ lọ sí ọ̀nà tí ó tọ́, sì fi ẹsẹ̀ wa rinlẹ̀ títí tí a ó fi pàdé Rẹ. |
| **{Ojú ọ̀nà àwọn ẹni tí O ṣe ìdẹ̀ra fún}** | Ọ̀nà àwọn ẹni tí O ṣe ìdẹ̀ra fún pẹ̀lú ìmọ̀nà àti dídúró déédé lórí ẹ̀sìn Ọlọ́hun, nínú àwọn Ànábì àti àwọn ẹni rere, tí wọ́n mọ òdodo, tí wọ́n sì tẹ̀lé. |
| **{Yàtọ̀ sí àwọn tí wọ́n ti di ẹni ìbínú sí tàbí àwọn ẹni tí wọ́n ti ṣọnù}** | Gbé wa jìnnà, kí O sì là wá níbi ọ̀nà àwọn ẹni tí O ti bínú sí, nítorí pé wọ́n mọ òdodo, wọn kò sì mú un lò, tún gbé wa jìnnà sí ọ̀nà àwọn ẹni tí ó ti ṣọnù, àwọn ni àwọn ẹni tí wọn kò mọ̀nà lọ síbi òdodo nítorí àìmọ̀kan wọn àti àṣeètó wọn nípa wíwá a. |
| **{Āmīn}** | Ìrẹ Ọlọ́hun! Gba àdúrà wa. |


## Kálukú ni ó ní gbólóhùn tí yóò sọ gbẹ̀yìn:

Lẹ́yìn gbogbo èyí, gbólóhùn ìgbẹ̀yìn tí yóò ṣẹ́kù fún gbogbo wa, níbi ìdàjọ́ rẹ̀ lórí *Al-Qur'ān* àti ipò tí yóò dúró sí nípa rẹ̀, yóò jẹ yọ látara ìrírí tìka lára rẹ̀, nígbà tó ń kà á, tó ń gbé e yẹ̀wò, tó sì ń ronú sí i, pẹ̀lú ṣíṣe ojú kòkòrò lóríi ṣíṣẹ̀ṣà ìtumọ̀ tó bá èdè rẹ̀ mu, tí kò bá jẹ́ Lárúbáwá.

Dájúdájú ó wá, nínú *Al-Qur'ān*, pé dájúdájú ẹ̀rí tó tóbi jùlọ lóríi jíjẹ́ òdodo ìjẹ́-Ànábì Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – ni ohun tí à ń débẹ̀ pẹ̀lú ọkàn wa àti láàkàyè wa, nínú àwọn àwárí-ìmọ̀, lẹ́yìn tí a bá kà, tí a sì ronú sí àwọn ìtumọ̀ *Al-Qur'ān*, Ọlọ́hun sọ wí pé: **"Ṣe ko ti to wọn ni pe dájúdájú Àwa sọ Tírà kalẹ̀, tí a n ke e fún wọn? Dájúdájú àánú àti irántí ń bẹ níbẹ̀ fún àwọn ènìyàn tí wọn gbàgbọ́ lódodo"** (*Al-'Ankabūt*: 51).

Ó da ojú ìpèpè kọ gbogbo wa pẹ̀lú kíka *Al-Qur'ān*, ríronú sí i àti fífi ọkàn bá a lọ. Àti pé ẹnìkankan kò ní kọ̀ láti ṣe èyí àyàfi ẹni tí wọ́n ti fi àwọn àgádágodo ti ọkàn àti làákàyè rẹ̀ pa. **"Ṣe wọn ko ronu si *Al-Qur'ān* ni, abi ọkan wọn ti dipa pẹ̀lú àwọn àgádágodo wọn ni?"** (*Muḥammad*: 24).





# Àwọn ìjọsìn nínú ẹ̀sìn *Islām*, kín ni pàápàá wọn?

### Ṣé Ọlọ́hun bùkáátà sí ìjọsìn wa?

Ọlọ́hun Ọba Abiyì, tí Ó ga, kò bùkáátà sí ìjọsìn wa àti àwọn iṣẹ́ wa. Ọlà àti yíyege, nínú ẹ̀sìn Islām, kò mọ lórí àwọn ètò ìjọsìn, àwọn ìrísí àti àwọn fífi owó dá ọlá. Ṣùgbọ́n pẹ̀lú bí jíjẹ́ òdodo dída ojú kọ Ọlọ́hun àti ìgbàgbọ́ òdodo ẹ̀dá pẹ̀lú Rẹ̀ bá ti tó, èyí tí ó ṣe ọ̀ranyàn kí á tú, ní ayé òde-òní, sí dídàgbàsòkè ẹ̀mí àti ìwà àti ṣíṣiṣẹ́ láti sin àwùjọ ọmọnìyàn àti gbígbìyànjú láti mú ìlọsíwájú bá a.

Ọlọ́hun sọ, nínú *Al-Qur'ān*, wí pé: **"Àti pé mi ò dá àwọn àlùjànnú ati àwọn ènìyàn lásán àyàfi nítorí kí wọ́n le máa jọ́sìn fún Mi. Mi ò fẹ́ ìpèsè kankan láti ọ̀dọ̀ wọn. Mi ò sì fẹ́ kí wọ́n fún Mi ní oúnjẹ. Dájúdájú Ọlọ́hun, Òun gan-an ni Olùpèsè fúnni, Alágbára, Olùkáátò"** *{Adh-Dhāriyāt:* 56-58}.

Nígbà tí ìrújú bá àwọn ènìyàn kan, tí wọ́n sì ń bèèrè pé; kín ni ìwòye tí ó ní àlááfìà nípa gábàsì tí à ń da ojú kọ kírun – èyí rí bẹ́ẹ̀, nítorí pé ìrun, nínú ẹ̀sìn *Islām*, jẹ́ ohun tí a máa ń da ojú rẹ̀ kọ ọ̀gangan ìlú *Makkah* – èsì wá pẹ̀lú kíkanpá mọ́ ọn fún wọn pè dájúdájú pàápàá ẹ̀sìn Islām ń bẹ níbi òtítọ́-inú níbi ìgbàgbọ́ àti dída ojú kọ Ọlọ́hun, àti ṣíṣe àwọn iṣẹ́ dáadáa àti ṣíṣe àwọn ènìyàn ní ànfààní, kì í ṣe dída ojú kọ ibùyọ tàbí ibùwọ̀ oòrùn níkan, Ọlọ́hun sọ fún wọn pé: **"Kì í ṣe dáadáa ni kí ẹ máa da ojú yín kọ ibùyọ tàbí ibùwọ̀ oòrùn, ṣùgbọ́n dáadáa ni ẹni tí ó ba ní ìgbàgbọ́ pẹ̀lú Ọlọ́hun, àti Ọjọ́ ìkẹ́yìn, àti àwọn *Malā'ikah* àti Tírà, àti àwọn Òjíṣẹ́, tí ó si tún ná owó pẹ̀lú ìfẹ́ ti ẹ̀ náà fún un, fún àwọn alásúnmọ́, àti àwọn ọmọ òrukàn, àti àwọn aláìní, àti ọmọ oju ọ̀nà (arìnrìn-àjò tí nǹkan tán mọ́ lọ́wọ́ níbi tí kì í ṣe ìlú rẹ̀), àti àwọn tí wọ́n ń tọrọ àti láti bọ́kun ẹrú, tí ó sì ń gbé ìrun nàró, tí ó sì ń yọ ọrẹ àànú ọ̀ranyàn *(Zakāh)*, àti àwọn tí wọ́n máa ń pé àdéhùn wọn nígbà tí wọ́n bá ṣe àdéhùn, àti àwọn tí wọ́n máa ń ṣe sùúrù nígbà òsí, àìsàn àti ní àsìkò ogun. Àwọn wọ̀nyẹn ni wọ́n sọ òdodo (níbi ìgbàgbọ́ wọn), àwọn wọ̀nyẹn sì ni olubẹ̀rù Ọlọ́hun"** (*Al-Baqarah:* 177).

*Al-Qur'ān* tún kàn án nípa fún wa, ní ìgbà mìíràn, pé dájúdájú ẹnikẹ́ni tí ó bá gbìyànjú níbi ìjọsìn àti ṣíṣe ẹ̀sìn, ó ṣe èyí fún ànfààní ẹ̀mí ara rẹ̀ àti ọlà rẹ̀ ni. Ṣùgbọ́n ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe àìgbàgbọ́, òun fún ara rẹ̀ níkan ni ẹni òfò, Ọlọ́hun sì rọrọ̀ kúrò ní ọ̀dọ̀ wa, gẹ́gẹ́ bí Ó ti sọ wí pé: **"Àti pé ẹnikẹ́ni tí ó bá gbìyànjú, dájúdájú ó gbìyànjú fún ẹ̀mí ara rẹ̀ ni. Dájúdájú Ọlọ́hun jẹ́ Olùrọrọ̀ kúrò ní ọ̀dọ̀ gbogbo àgbáyé"** (*Al-'Ankabūt*: 6).



"Nígbà tí ìrújú bá àwọn ènìyàn kan, tí wọ́n sì ń bèèrè pé; kín ni ìwòye tí ó ní àlááfìà nípa gábàsì tí à ń da ojú kọ kírun – èyí rí bẹ́ẹ̀, nítorí pé ìrun, nínú ẹ̀sìn *Islām*, jẹ́ ohun tí a máa ń da ojú rẹ̀ kọ ọ̀gangan ìlú *Makkah* – èsì wá pẹ̀lú kíkanpá mọ́ ọn fún wọn pè dájúdájú pàápàá ẹ̀sìn *Islām* ń bẹ níbi òtítọ́-inú níbi ìgbàgbọ́ àti dída ojú kọ Ọlọ́hun, àti ṣíṣe àwọn iṣẹ́ dáadáa àti ṣíṣe àwọn ènìyàn ní ànfààní, kì í ṣe dída ojú kọ ibùyọ tàbí ibùwọ̀ oòrùn níkan.




## Àwọn orígun ìrun:

Èyí ni àwọn ìjọsìn tó pàtàkì jùlọ, èyí tí wọ́n pa wa láṣẹ rẹ̀ nínú ẹ̀sìn *Islām*, àlàyé rẹ̀ ni ń bọ̀ yìí:



Ìgbàgbọ́ òdodo àti fífi ṣíṣe àfọ̀mọ́ ìjọsìn fún Ọlọ́hun àti títẹ̀lé Ìránṣẹ́ Rẹ̀, Muḥammad rinlẹ̀, èyí yóò wáyé pẹ̀lú pé kí o jẹ́rìí pé kò sí ọlọ́hun kankan tí ó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn àyàfi Ọlọ́hun Allāh nìkan, àti pé Muḥammad, níti pàápàá, jẹ́ Ìránṣẹ́ Rẹ̀. (wo: ojú-ewé 32)



Gbígbé àwọn ìrun ọ̀ranyàn dúró (wo: ewé 100)



Yíyọ *Zakāh* fún àwọn tó ní ẹ̀tọ́ sí i (wo: 104 ewé )



Gbígba ààwẹ̀ oṣù *Ramaḍān* (wo: ewé 106)



Ṣíṣe ìrìn-àjò lọ sí ilé Ọlọ́hun àbọ̀wọ̀, fún àwọn tó ní agbára rẹ̀, ní owó àti ara (wo: ewé 108)

## Kín ni ó fa lila iwọ̀ bọ wa lọ́rùn àti dídán wa wò?

Ìbéèrè kò yé máa wáyé, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé pẹ̀lú àgbékalẹ̀ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, ẹnìkan nínú wọn wí pé: Kílódé tí Ọlọ́hun dá ẹnu fún wa, àti àwọn eyìn àti ìfun nítorí kí á le jẹun, lẹ́yìn náà tí yóò tún wá wí pé: Ẹ máa gba ààwẹ̀?! Kílódé tí Ó dá ẹwà àti adún fún wa, lẹ́yìn náà tí yóò tún wá wí pé: Ẹ máa rẹ ojú yín nílẹ̀, ẹ sì ní àmójúkúrò! Ẹlòmíràn le ṣe àyà gbàǹgbà, kí ó wí pé : Kílódé tí Ó fún wa ní agbára, lẹ́yìn náà tí yóò tún wá kọ̀ fún wa láti tayọ ààlà lórí àwọn ẹlòmíràn àti ṣíṣe àbòsì fún wọn?

Pàápàá ọ̀rọ̀ ni pé dájúdájú ọ̀ràn yìí ti hàn dé òpin nínú iwòye ẹ̀sìn Islām. Ọlọ́hun fún wa ní àwọn ìkápá àti àwọn agbára nítorí kí ó le jẹ́ wí pé àwa ni a ó máa darí rẹ̀, kì í ṣe nítorí kí ó le jẹ́ wí pé òhun ni yóò máa darí wa.. Ọlọ́hun (ní àpèjúwe) fún ọ ní ẹṣin, kí o lè máa gùn ún, kí ó sì máa darí rẹ̀, kì í ṣe kí ó le máa gùn ọ́, kí ó sì máa darí rẹ̀. Ara wa àti agbára wa ní àwọn ẹṣin wa tí Ọlọ́hun dá fún wa, kí á le máa gùn ún, kí á máa darí rẹ̀, kí á sì máa fún un ní ìjánu, kí á sì máa lò ó ní àsìkò, ààyè àti ọ̀nà tí ó ní àlááfià, kì í ṣe ìdàkejì èyí.

Fún ìdí èyí, ipò ènìyàn àti dídi ẹni gíga rẹ̀, wà níbi agbára rẹ̀ lórí kíkó ara rẹ̀ ní ìjánu níbi adún, dídarí ìfẹ́-inú àti ẹ̀mí rẹ̀ àti dídarí àwọn agbára wọ̀nyí síbi ohun tí yóò ṣe àǹfààní.. Èyí ni Ọlọ́hun fi ṣe àdáyanrí ènìyàn, Ó sí pèsè gbàgede àdánwò sílẹ̀ fún un... Èyi ni Ọlọ́hun dá wa nítorí rẹ̀.

Gẹ́gẹ́ bí *Al-Qur'ān* ti sọ wí pé: **{Dájúdájú Àwa ni A dá ènìyàn látara omi lọ́gbọ̀lọ́gbọ̀ tí ó pòpọ̀, kí Á le dán an wò, nítorí náà A ṣe é ní olùgbọ̀ràn, olùríran. Dájúdájú Àwa ni A fi ọ̀nà mọ̀ ọ́n! Yálà yóò jẹ́ olùdúpẹ́ ni tàbí aláìmoore}** (*Al-'Insān:* 2- 3).

Gbogbo ohun tí ó bá bá ènìyàn nínú àwọn àdánwò àti wàhálà, kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe abala àdánwò kan, nítorí kí á le mú ìdàgbàsókè bá àwọn ìṣesí wa nínú ẹ̀mí, ìwà àti ìgbàgbọ́ òdodo. Àti nítorí kí á le tún rántí àfojúsùn wa àti ipò wa nínú ìṣẹ̀mí-ayé yìí yẹ̀wò. Gẹ́gẹ́ bí ó ti wá nínú *Al-Qur'ān* pé: **"Dájúdájú A ó máa dan yín wò pẹ̀lú nǹkankan nínú ìbẹ̀rù, àti ebi, àti ìdínkù nínú àwọn dúkìá, àti àwọn ẹ̀mí àti àwọn èso, ṣùgbọ́n fún àwọn onísùúrù ní ìró ìdùnnú- Àwọn ẹni tí ó ṣe pé, nígbà tí àdánwò bá bá wọn, wọn yóò wí pé: Dájúdájú ti Ọlọ́hun ni àwa á ṣe (abẹ́ Ìkápá Rẹ̀ ni a wà), dájúdájú ọ̀dọ̀ Rẹ̀ náà ni a ó sì padà sí"** (*Al-Baqarah:* 155-156).

Àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nítorí náà ìṣẹ̀mì-ayé yìí, ní ààyè tí wọ́n ti fún wa ní àǹfààní láti wá ìlọsíwájú tàbí ìfàsẹ́yìn tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ìgbàgbọ́ àti ìhùwàsí. Ọlọ́hun, mímọ́ ni fún Un, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé dájúdájú Ó fún wa ní àwọn àǹfààní léraléra fún ìmọ̀nà àti ṣíṣe àtúnṣe, ṣùgbọ́n kò jẹ wá nípá lórí rẹ̀. Bíbẹ́ẹ̀ kọ́ Ó ṣí ìlẹ̀kùn kalẹ̀ fún wa láti ṣẹ̀ṣà, Ó sì gbà wá níyànjú láti máa gbé orí ilẹ̀, ṣíṣe àwọn ènìyàn ní àǹfààní àti kíkọ́gbọ́n níbi àwọn àṣìṣe wa àti àwọn ìgbìyànjú wa, pẹ̀lú pé kí á ṣẹ́rí padà, kí á sì ronúpìwàdà lọ sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀, ní gbogbo ìgbà tí àṣìṣe àti àìṣe déédé bá ti hàn sí wa. Dájúdájú Ànábì alápọ̀n-ọ́nlé, Muḥammad – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – sọ wí pé: "Tí ó bá jẹ́ wí pé ẹ kò máa dá ẹ̀ṣẹ̀ ni, dájúdájú Ọlọ́hun kò bá pa yín run, kò bá sì mú àwọn ìjọ mìíràn tí wọn yóò máa dá ẹ̀ṣẹ̀ wá, ṣùgbọ́n tí wọn yóò máa tọrọ àforíjin, tí yóò sì máa ṣe àforíjìn fún wọn" (*Muslim*: 2749).



> Ipò ènìyàn àti dídi ẹni gíga rẹ̀, wà níbi agbára rẹ̀ lórí kíkó ara rẹ̀ ní ìjánu níbi adún, dídarí ìfẹ́-inú àti ẹ̀mí rẹ̀ àti dídarí àwọn agbára wọ̀nyí síbi ohun tí yóò ṣe àǹfààní..

# Ìrun kíkí

Bóyá o ti fi ìgbà kan bèèrè rí; nípa pàápàá ọ̀ràn, nígbà tí ó ri ìrísí tí ó ya ènìyàn lẹ́nu, ní fètetè, tàbí lórí àwọn ilé àti ìwé ìròyìn, ní ibi tí Mùsùlùmí kan tàbí jú bẹ́ẹ̀ lọ tí da ojú kọ ààyè kan pàtó, tí wọ́n sì bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú nínàró, títẹ̀ kọ̀kọ̀rọ̀ àti ìforíkanlẹ̀, bíi ẹni pé wọ́n ti pa ilé-ayé tí ó wà ní ẹ̀gbẹ̀ẹ̀gbẹ́ wọn tì..

## Kín ni ìrun tí àwọn Mùsùlùmí ń kí?

Ìrun kíkí rí pípàtàkì rẹ̀ tí ó tóbi jùlọ nínú ẹ̀sìn Islām, nítorí pé òhun ni ọ̀nà tí ó pàtàkì jùlọ fún sísúnmọ́ Ọlọ́hun, pípè É àti títẹríba fún Un. Gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́hun ti sọ fún Ànábì Rẹ̀ pé: "Ṣùgbọ́n kí o foríbalẹ̀, kí o sì súnmọ́ (Ọlọ́hun)" (Al-'Alaq: 19). Fún ìdí èyí, òhun ni orígun kejì nínú àwọn orígun ẹ̀sìn Islām, lẹ́yìn pípe gbólóhùn ìjẹrìí méjèèjì.

Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – sọ wí pé: "A mọ ẹ̀sìn Islām lórí ìpìlẹ̀ márùn-ún: Ìjẹ́rìí pé dájúdájú kò sí ọlọ́hun kankan tí ó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn àyàfi Ọlọ́hun Allāh nìkan, àti pé Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun Muḥammad, níti pàápàá, jẹ́ Ìránṣẹ́ Rẹ̀, gbígbé ìrun dúró.. " (Al-Bukhārī: 8).


Wọ́n yóò san Mùsùlùmí ní ẹ̀san rere lórí ìrun rẹ̀ – gẹ́gẹ́ bí ẹ̀sìn Islām ti kọ́ wa – pẹ̀lú bí ìgbìyànjú akírun bá ti mọ níbi ṣíṣe àfọ̀mọ́ ọkàn rẹ̀, pípa ọkàn rẹ̀ pọ̀ àti ṣíṣe àwọn èrò rẹ̀ lọ́kan àti òtítọ́-inú níbi fífi ara ralẹ̀ fún Ọlọ́hun rẹ̀, àti fífura mọ sísúnmọ́ Ọlọ́hun rẹ̀, pẹ̀lú ohun tí yóò fún ẹ̀mí ní ìfàyàbalẹ̀ àti ìrọ̀ra rẹ̀, èyí ni ó fà á tí ó fi jẹ́ wí pé ìrun ni adùn tí ó tóbi jùlọ fún Ànábì – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a –.

Fún ìdí èyí, *Al-Qur'ān* ṣe wá lójú kòkòrò pé kí á máa gbérun nàró, kì í ṣe kí á kàn máa kí i lásán. Nítorí pé dájúdájú pàápàá gbígbé ìrun nàró, gbogbo oríkèé ara, pẹ̀lú làákàyè, ọkàn àti ẹ̀mí.. ni yóò kópa níbẹ̀. Àti pé dájúdájú nígbà tí a bá ti ṣe èyí, ìrun; fún wa, yóò jẹ́ olùrànlọ́wọ́ lórí ṣíṣe àwọn dáadáa àti jíjìnnà sí àwọn ìwà ọ̀daran àti àwọn ohun tí ó máa ń kó ìparun bá ènìyàn. Nítorí pé ìrántí àti wíwá ìsádi lọ ọ̀dọ̀ Rẹ̀ ni ohun tí ó tóbi jùlọ nínú gbogbo ohun tí ènìyàn máa ń ṣe pátápátá. Ọlọ́hun, sọ wí pé: "Dájúdájú ìrun máa n kọ̀ nípa àwọn ìbàjẹ́ àtí ohun tí ọkàn kọ̀ àti pé dájúdájú Ìrántí Ọlọ́hun ni ó tóbi jùlọ. Ọlọ́hun sì mọ ohun tí ẹ̀ ń ṣe" (Al-'Ankabūt: 45).

Ẹnikẹ́ni tí ó bá lèrò pé ìrun kò ju ìdárayá àfaraṣe lásán lọ, èyí tí ìwẹ̀ àti ìmọ́ra máa ń síwájú rẹ̀, dájúdájú ó ti ṣe àfẹ́kù pé ohun tí ó rí nínú àwọn iṣẹ́ ìrun, kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe àwọn iṣẹ́ àti àwọn ọ̀rọ̀ tí ó wà fún gbígbé Ọlọ́hun tóbi àti bíbàbàrà Rẹ̀ nínú àwọn ẹ̀mí. Àkọ́kọ́ gbólóhùn tí àkírun yóò sọ, pẹ̀lú gbígbé ọwọ́ rẹ̀ méjèèjì sókè ni: (Allāhu 'Akbar: Ọlọ́hun ni Ó tóbi jùlọ). Lẹ́yìn náà yóò rúkúù (tẹ̀ kọ̀kọ̀rọ̀) pẹ̀lú ìtẹríba, ní ẹni tí ó fi títóbi Ọlọ́hun sí ọkàn, ní ẹni tí ó gbà pé òhun kágara, yóò sì sọ wí pé: (Subḥāna Rabbiyal-'Aẓīm: Mímọ́ ni fún Ọlọ́hun Ọba mi, Ọba tí Ó tóbi). Lẹ́yìn náà yóò fi orí kanlẹ̀ fún Ọlọ́hun, ní ẹni tí ń wá sísúnmọ́ Ọn àti gbígba àdúà òun, yóò sì gbé ìwájú-orí rẹ̀ àti imú rẹ̀ lélẹ̀ ní ẹni tí ó sọ wí pé: (Subḥāna Rabbiyal-'A'lā: Mímọ́ ni fún Ọlọ́hun Ọba mi, Ọba tí Ó ga jùlọ). Yóò pe Ọlọ́hun Ọba rẹ̀, yóò tọrọ ní ọ̀dọ̀ Rẹ̀... Báyìí ni gbogbo àwọn iṣẹ́ ìrun àti àwọn ọ̀rọ̀ orí rẹ̀; kì í ṣe àwọn iṣẹ́ àti kíkálòlò lásán. Ṣùgbọ́n ó jẹ́ àwọn àsìkò tí ó rọrọ̀ gidigidi, èyí tí yóò so olùgbàgbọ́ òdodo mọ́ Ọlọ́hun Ọba rẹ̀ àti Olùṣẹ̀dá rẹ̀, Ẹni tí ó jẹ́ wí pé láti ọ̀dọ̀ Rẹ̀ ni ó ti ń rí bíbẹ rẹ̀ àti oríire rẹ̀.



Ìrun jẹ́ adùn tí ó tóbi jùlọ fún Ànábì Muḥammad – kí ìkẹ́ àti ọlà Ọlọ́hun máa bá a –.



Mọ̀ṣálásí Abọ̀wọ̀ ni Mọ̀ṣálásí tí ó pàtàkì jùlọ ní ọ̀dọ̀ àwọn Mùsùlùmí. Ka‘bah, èyí tí Ibrāhīm kọ́, wà níbẹ̀. Èyí ni ilé roboto tí wọ́n pa àwọn Mùsùlùmí láṣẹ, nínú *Al-Qur’ān* láti máa da ojú kọ ọ́, láti gbogbo ààyè tí ó wà ní àgbàyé fún ìrun kíkí pẹ̀lú àdìsọ́kàn pé dájúdájú kò le ni ènìyàn lára, kò sì le ṣe é ní àǹfààní.

Ọlọ́hun ṣe ìrun márùn-ún ní ọ̀ranyàn lórí àwọn Mùsùlùmí ní ọ̀sán àti òru, kíkí i ní àlááfíà ní ààyèkááyè tí a bá wà, síbẹ̀síbẹ̀ dájúdájú ó gbà wọ́n níyànjú pé kí wọ́n máa kí i ní àwọn Mọ̀ṣálásì nítorí kí àjọṣepọ̀ àwọn Mùsùlùmí pẹ̀lú ara wọn le máa jinlẹ̀ sí i, kí àwọn ohun tó so wọ́n papọ̀ le máa lágbára sí i, kí wọ́n sì máa ran ara wọn lọ́wọ́ lórí ọ̀ràn ayé àti ẹ̀sìn.

Gẹ́gẹ́ bí ẹ̀sìn *Islām* ti gbà wá níyànjú lórí ṣíṣe ìgbìyànjú láti máa yan àwọn *Nāfilah* (èyí ni àwọn ìrun tí kì í ṣe ọ̀ranyàn), ní ìgbà tí Mùsùlùmí bá ti rí i pé ara òun yágágá láti ṣe èyí.

Àwọn Mùsùlùmí máa ń kí ìrun wọn, nígbà tí wọ́n yóò sì kọjú sí ọ̀gangan *Ka‘bah*, èyí ni ilé tí ìrísí rẹ̀ rí roboto. Àkọ́kọ́ ẹni tí ó kọ́ ọ̀ ni Ibrāhīm, èyí tí wọ́n máa ń ròyìn rẹ̀ pẹ̀lú pé òun ni bàbá àwọn Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a-, ní ìlú *Makkah*, ní ìwọ̀ oòrùn erékùsù ilẹ̀ Lárúbáwá, àwọn Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá wọn – sì wà ṣe ìjọsìn *Ḥajj* níbẹ̀. Àwọn Mùsùlùmí sì mọ̀ pé àkójọpọ̀ àwọn òkúta ni, kò le ni ènìyàn lára, kò sì le ṣe é ní àǹfààní. Ṣùgbọ́n Ọlọ́hun pàṣẹ kí á máa da ojú kọ ọ́ níbi ìrun nítorí kí àwọn Mùsùlùmí le jẹ́ ọ̀kan níbi dída ojú kọ agbègbè kan ṣoṣo.

## Ìrun pípè:

Wọ́n ń pe pipe, èyí tó ń ta àwọn ènìyàn jí sí wí pé àsìkò ìrun ti wọlé, tí ó sì ń pè wọ́n pé kí wọ́n máa bọ̀ wá kírun ní (*Adhān*).

Ó sì jẹ́ ìran kan nínú ìrántí Ọlọ́hun àti gbígbé E tóbi, àti pípèsè àwọn Mùsùlùmí sílẹ̀ fún wíwá kírun, èyí ni àwọn gbólóhùn rẹ̀:

1- *Allāhu ’Akbar, Allāhu ’Akbar, Allāhu ’Akbar, Allāhu ’Akbar* (Ọlọ́hun ni Ó tóbi jùlọ, Ọlọ́hun ni Ó tóbi jùlọ, Ọlọ́hun ni Ó tóbi jùlọ, Ọlọ́hun ni Ó tóbi jùlọ).

2- *’Ashhadu ’an lā ’ilāha ’illallāh,’Ashhadu ’an lā ’ilāha ’illallāh* (Mo jẹ́rìí pé kò sí ọlọ́hun kan tí ó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn àyàfi Ọlọ́hun Allāh, Mo jẹ́rìí pé kò sí ọlọ́hun kan tí ó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn àyàfi Ọlọ́hun Allāh).

3- *’Ashhadu ’anna Muḥammadan rasūlullāh,’ashhadu ’anna Muḥammadan rasūlullāh* (Mo jẹ́rìí pé (Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun) Muḥammad, níti pàápàá, jẹ́ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun, mo jẹ́rìí pé (Òjíṣẹ́ Ọlọ́hun) Muḥammad, níti pàápàá, jẹ́ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun).

4- *Ḥayya ‘alaṣ-ṣalāh, ḥayya ‘alaṣ-ṣalāh* (Ẹ yára wá kírun, ẹ yára wá kírun).

5- *Ḥayya ‘alal-falāḥ, ḥayya ‘alal-falāḥ* (ẹ yára wá jèrè, ẹ yára wá jèrè).

6- *Allāhu ’Akbar, Allāhu ’Akba*r (Ọlọ́hun ni Ó tóbi jùlọ, Ọlọ́hun ni Ó tóbi jùlọ).

7- *Lā ’ilāha ’illallāh,* (Mo jẹ́rìí pé kò sí ọlọ́hun kan tí ó lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn àyàfi Ọlọ́hun Allāh).

# *Zakāh* yíyọ

Gbogbo ènìyàn ni ó mọ̀ dájú pé a gbọdọ̀ wá ojútùú sí nǹkan méjì; ọrọ̀ àníjù àti òsì rádaràda. Àti pé dájúdájú bí àlàfo tí ó wà láàrìn àwọn ọlọ́rọ̀ àti àwọn aláìní bá ti mọ, bẹ́ẹ̀ náà ni ìfàsẹ́yìn tí yóò bá àwùjọ àti kíkó sínú àwọn ìwà iyẹpẹrẹ, ìwà ọ̀daràn àti fífọ́n yẹ́lẹyẹ̀lẹ rẹ̀, yóò ti mọ. Dájúdájú orísirísi àwọn ètò ọrọ̀-ajé, àwọn àgbélẹ̀rọ ìrörí àti àwọn àgbékalẹ̀ òfin ní ó wà fún wíwá ojútùú sí ìṣòro yìí.. Báwo wáà ni ẹ̀sìn *Islām* ti bá a lò?

Ọlọ́hun ṣe *Zakāh* yíyọ ní ọ̀ranyàn lórí àwọn ọlọ́rọ̀ Mùsùlùmí, pé kí wọ́n máa yọ 2.5% nínú dúkìá wọn, èyí tó ṣẹ́kù lẹ́yìn àwọn ohun-ìní wọn, èyí tí wọ́n bùkáátá sí fún ara wọn, ní gbogbo ọdọọdún. Nítorí kí á le pín in fún àwọn tó bùkáátá sí i nínú àwọn tálákà àti àwọn aláìní àti ẹni tó bá rí bíi wọn, Ó sì ṣe èyí ní orígun kẹta nínú àwọn orígun ẹ̀sìn *Islām*

Kò sí ìdọ̀lá, níbi yíyọ *Zakāh*, láti ọ̀dọ̀ ọlọ́rọ̀ fún tálákà. Ṣùgbọ́n ó jẹ́ ẹ̀tọ́ fún tálákà, èyí tí a ó yọ nínú àwọn dúkìá ọlọ́rọ̀, tí yóò sì dé ọ̀dọ̀ ẹni tí ó bùkáátà sí i, láìṣe pé ó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń bèèrè fún un tàbí fífi iyì rẹ̀ wọ́lẹ̀.

Ìwọ̀nba kékeré yìí, nínú nínáwó, òun ni ohun tó ṣe ọ̀ranyàn lórí Mùsùlùmí tó jẹ́ ọlọ́rọ̀. Ṣùgbọ́n ààlà tó ga jùlọ nínú nínáwó, ìgbàlááyè ń bẹ fún àwọn ènìyàn láti bá ara wọn ta kànǹgbàn níbẹ̀, wọn yóò sì máa rí orípa nínáwó yìí nínú ìṣẹ̀mí wọn, níbi àlááfíà àti dúkìà, níbi kòǹgẹ́ àti orí rere, àti ẹ̀san rere àti àdìpèlé ìdẹ̀ra ní ọ̀run.

Gẹ́gẹ́ bí ó ti wá nínú *Al-Qur'ān* pé: Dájúdájú àwọn ẹni tí wọ́n máa ń ná owó wọn láti fi wá Ìyọ́nú Ọlọ́hun dà bíi hóró álíkámà, tí wọ́n gbìn, tí ó sì hu ṣiri méje, tí ọgọ́rùn-ún hóró sí wà nínú gbogbo ṣiri kọ̀ọ̀kan, lẹ́yìn náà tí ó tún dí àdìpèlé ní ìlọ́po ọgọ́rùn-ún méje, ṣùgbọ́n Ọlọ́hun máa ń ṣe àlékún rẹ̀ báyìí, ní ibámu sí bí òtítọ́-inú ẹni tí ó ń náwó àti èròǹgbà rẹ̀ bá ti rí. Ọlọ́hun gbààyè ní ọrẹ, Ó sì jẹ́ Alámọ̀tàn pẹ̀lú pàápàá àwọn ọ̀ràn.



Kò sí ìdọ̀lá, níbi yíyọ *Zakāh*, láti ọ̀dọ̀ ọlọ́rọ̀ fún tálákà. Ṣùgbọ́n ó jẹ́ ẹ̀tọ́ fún tálákà, èyí tí a ó yọ nínú àwọn dúkìá ọlọ́rọ̀, tí yóò sì dé ọ̀dọ̀ ẹni tí ó bùkáátà sí i, láìṣe pé ó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń bèèrè fún un tàbí fífi iyì rẹ̀ wọ́lẹ̀.




*Al-Qur'ān* fún wa ní ìró pé dájúdájú nínáwó fún àwọn aláìní jẹ́ àfọ̀mọ́ fún ẹ̀mí. Ó máa ń fọ̀ ọ́ mọ́. Ọlọ́hun, nígbà tó ń bá Ìránṣẹ́ Rẹ̀ alápọ̀n-ọ́nlé sọ̀rọ̀, sọ wí pé: **"Mú nínú àwọn dúkìá wọn; ọrẹ àánú (*Zakāh*) tí yóò máa fọ̀ wọ́n mọ́ tí ó sì máa sọ wọ́n di mímọ́ pẹ̀lú rẹ̀"** (*At-Tawbah*: 103).

Ó tún fún wa ní ìró, bákan náà, pé dájúdájú ẹni tó bá ń ṣe ahun pẹ̀lú owó rẹ̀, tó sì ń kọ̀ láti ná an àti láti ran àwọn tálákà àti àwọn aláìní lọ́wọ́, òun ni àkọ́kọ́ àwọn ẹni òfò. Nítorí pé dájúdájú ó ń ṣe ahun sí ara rẹ̀ pẹ̀lú orí rere ayé àti ti ọ̀run. **"Kíyèsi! Ẹyin ni àwọn ẹni tí wọ́n ń pè, kí ẹ le náwó sí Ọ̀nà Ọlọ́hun, ṣùgbọ́n ẹni tí ó ń ṣe ahun ń bẹ nínú yín. Àti pé ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe ahun, ẹ̀mí ara rẹ̀ nìkan ní ó ṣe ahun fún. Àti pé Ọlọ́hun ni Ọlọ́rọ̀, ẹyin sì ni aláìní. Tí ẹ bá sì yí ẹ̀yìn padà, yóò fi àwọn ènìyàn mìíràn yatọ̀ si yín pààrọ̀ yín, lẹ́yìn náà wọn kò ní jẹ́ irú yín"** (*Muḥammad*: 38).

Pẹ̀lú ṣíṣe àmúlò orígun tí ó tóbi yìí, nínú àwọn orígun ẹ̀sìn Islām, ní pàápàá ìfàyàbalẹ̀ àwùjọ yóò fi fẹsẹ̀ múlẹ̀, àti ṣíṣe déédé ránpẹ́ láàrin àwọn ènìyàn àwùjọ, pẹ̀lú yíyọ *Zakāh* fún àwọn ẹni tí ó ní ẹ̀tọ́ sí i, ọrọ̀ owó kò ní ṣodo sí ọwọ́ àwọn ènìyàn kan níkan nínú àwùjọ, kò sì ní jẹ́ ohun tí a kò pamọ́ sí ọ̀dọ̀ wọn nìkan. Èyí ni ó fà á, tí ó fi jẹ́ wí pé nínú ìtàn àwọn Mùsùlùmí àkọ́kọ́, ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, ní ó ṣẹlẹ̀ pé wọ́n ń gbé *Zakāh* àti àwọn ohun tí wọ́n fẹ́ fi ran àwọn aláìní lọ́wọ́ yípo ìlú ká, láti wá ẹni tí ó bùkáátà í i, ṣùgbọ́n wọn kò ní rí.

Gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ wí pé ìpìlẹ̀ àsopọ̀ àti kíkó ara ẹni mọ́ra yóò fi ẹsẹ̀ rinlẹ̀. Ìdí èyí ni pé wọ́n dá ẹ̀mí ọmọnìyàn lórí ìfẹ́ ẹni tí ó bá ṣe dáadáa sí i. Pẹ̀lú èyí ni ènìyàn kọ̀ọ̀kan nínú àwùjọ Mùsùlùmí yóò fi máa ṣẹ̀mí pẹ̀lú ìfẹ́ láàrin ara wọn, tí wọn yóò di ara wọn mú bíi ilé tí a mọ lọ́wọ̀ọ̀wọ́, tí apákan rẹ̀ so mọ́ apákejì. Ìṣẹ̀lẹ̀ olè jíjà, lílọ́ni lọ́wọ́ gbà àti jìbìtì yóò sì dínkù.

*Al-Qur'ān* fi àwọn ẹni tí wọ́n máa ń ná owó wọn láti fi wá Ìyọ́nú Ọlọ́hun dà bíi hóró álíkámà, tí wọ́n gbìn, tí ó sì hu ṣiri méje, tí ọgọ́rùn-ún hóró sí wà nínú gbogbo ṣiri kọ̀ọ̀kan, lẹ́yìn náà tí ó tún dí àdìpèlé ní ìlọ́po ọgọ́rùn-ún méje.



# Ààwẹ̀ gbígbà

Gbogbo wa ni a máa ń ṣe èǹmọ̀ nípa ẹni tó kó ara rẹ̀ ní ìjánu, tó sì lágbára láti má jẹun tàbí láti má jẹ àwọn ìran kan nínú rẹ̀, láti fi ṣọ́ àlááfíà ara rẹ̀, àti láti dín ìwọ̀n rẹ̀ kù tàbí láti tẹ̀lé àwọn ìmọ̀ràn dókítà.. A sì máa ń ka èyí sí ìyege àti àṣeyọrí nítorí pé ó lágbára láti borí àwọn adùn rẹ̀ nítorí àti rí àfojúsùn tó tóbi, tó sì pàtàkì jù ú lọ.

Mùsùlùmí, pẹ̀lú gbígba ààwẹ̀ rẹ̀, yóò ṣe ohun tí ó tóbi ju èyí lọ, láti fi re ara rẹ̀, àti láti kápá ara rẹ̀ àti àwọn adùn rẹ̀ àti láti mú àwọn àṣẹ Ọba tí Ó mọ ẹjọ́ dá ju gbogbo àwọn adajọ́ lọ lò.

Ààwẹ̀ gbígbà ni orígun kẹrin nínú ẹ̀sìn Islām, nítorí náà ẹ̀sìn Islām ṣe é ní ọ̀ranyàn fún ẹni tí ó bá ní agbára kí ó gba ààwẹ̀, kí ó sì kóra ró kúrò níbi àwọn ohun tí ó le já ènìyàn ní ààwẹ̀, èyí ni: Oúnjẹ jíjẹ, nǹkan mímu àti níní ìbálòpọ̀ pẹ̀lú ìyàwó rẹ̀, láti ìgbà tí àfẹ̀rẹ̀mọ́júmọ́ bá ti yọ, títí di ìgbà tí òòrùn yóò wọ̀, ní ojoojúmọ́ nínú oṣù Ramaḍān, èyí ni osù kẹsàn-án nínú oṣù ojú-ọ̀run nínú ònkà ti ẹ̀sìn *Islām*.

> Ànábì tí Ọlọ́hun fi ẹ̀sìn *Islām* rán pàkíyèsí wa sí wí pé ẹni tí ìṣesí rẹ̀ kò bá yàtọ̀, tí àwọn ìwà rẹ̀ kò sì dára sí i, lẹ́yìn ààwẹ̀ gbígbà, ààwẹ̀ rẹ̀ kò ṣe é ní àǹfààní.

*Al-Qur'ān* tún fún wa ní ìró pé dájúdájú ààwẹ̀ gbígbà jẹ́ ohun tí wọ́n ṣe ní ọ̀ranyàn fún àwọn ìjọ tí ó ti síwájú, bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ní ọ̀nà tí kò bá ara wọn mu ni, ní ìgbà mìíràn. Ṣùgbọ́n ohun tí wọ́n gbà lérò pẹ̀lú rẹ̀, ọ̀kan ṣoṣo ni, kò le yípada, èyí ni: Fífi pàápàá jíjẹ́-ẹrúsìn fún Ọlọ́hun àti pípáyà Rẹ̀ rinlẹ̀. Ọlọ́hun, nínú *Al-Qur'ān*, sọ wí pé: **"Ẹyin ẹni tí ó gbàgbọ́ lódodo! A ti ṣe ààwẹ̀ gbígbà ní ọ̀ranyàn lé yín lórí gẹ́gẹ́ bí A ti ó ṣe é ní ọ̀ranyàn lé àwọn ẹni tí ó síwájú yín lórí, nítorí kí ẹ le baà bẹ̀rù (Ọlọ́hun)"** (Al-Baqarah: 183).

Nígbà tí Mùsùlùmí bá ṣẹ́gun àwọn adùn rẹ̀ tó jẹ́ ẹ̀tọ́ fún àwọn wákàtí kan pàtó, ní gbogbo ọjọ́ fún àwọn ọjọ́ tó ní òǹkà, pẹ̀lú èyí, yóò di ọ̀gá ara rẹ̀, ẹni tó lágbára láti kó o ní ìjánu, tó sì le kọ̀ fún un kúrò níbi àwọn adùn tó jẹ́ èèwọ̀ nínú gbogbo àwọn ìṣesí ìṣẹ̀mí-ayé rẹ̀ tó ṣẹ́kù. Ìdí nìyí tí Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – fi ta wá jí sí wí pé ẹnikẹ́ni tí ìṣesí rẹ̀ kò bá yípadà, tí àwọn ìwà rẹ̀ kò sì dára sí i lẹ́yìn ààwẹ̀, kò ṣe àǹfààní níbi ààwẹ̀ rẹ̀ tó gbà. Ànábí – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wí pé: "Ẹnikẹ́ni tí kò bá fi ọ̀rọ̀ èké sílẹ̀, àti mímáa ṣiṣẹ́ pẹ̀lú rẹ̀, kò sí bùkáátà kankan fún Ọlọ́hun níbi kí ó fi oúnjẹ rẹ̀ àti nǹkan mímu rẹ̀ sílẹ̀" (*Al-Bukhārī*: 1804).

Ebi tó ń pa aláàwẹ̀ àti òǹgbẹ tó ń gbẹ ẹ́ yóò jẹ́ ohun tó tóbi jùlọ tí yóò máa jẹ́ kí ó gbìyànjú láti ṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn tálákà àti àwọn tí ebi ń pa, àwọn tí kó rí oúnjẹ jẹ tàbí rí nǹkan mu, pẹ̀lú pé wọ́n gba kámú, kìí ṣe pé ó wù wọ́n bẹ́ẹ̀, nítorí pé dájúdájú òun náà ti fi ara gbá nǹkankan nínú àwọn ìnira tó ń kojú wọn.



> Nígbà tí ẹ̀sìn *Islām* ṣe ààwẹ̀ gbígbà ní ọ̀ranyàn lórí Mùsùlùmí, dájúdájú ó ń rán an létí nípa ebi tí ó ń pa àwọn tálákà àti bíbùkáátà wọn sí oúnjẹ.

## *Ḥajj* ṣíṣe

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ẹ̀sìn kò pa sófo níbi ìrìn-àjò tó ní í ṣe pẹ̀lú ẹ̀sìn, ẹ̀yí tí yóò hàn sí àwọn ènìyàn nínú rẹ̀; ìjọsìn wọn àti ìfararalẹ̀ wọn fún Aṣẹ̀dá wọn.. Ṣùgbọ́n ẹ̀yí tí kò yẹ̀ ní ìrìn-àjò  tó gbajúmọ̀ jùlọ, tó sì pọ̀ jùlọ ní òǹkà, ní ọdọọdún, òun ni ìrìn-àjò *Ḥajj* nínú ẹ̀sìn *Islām*, nítorí pé ohun tó lé ní ọgbọ̀n mílíọ̀nù Mùsùlùmí yóò kóra jọ papọ̀ sí ààyè kékeré kan láti ṣe iṣẹ́ ìjọsìn ìrìn-àjò mímọ́ yìí.

**Kín ni ń jẹ́ *Ḥajj* ṣíṣe nínú ẹ̀sìn *Islām*?**

Ḥajj ṣíṣe ni orígun karùn-ún nínú àwọn orígun ẹ̀sìn Islām, kò sì jẹ́ ọ̀ranyàn àyàfi ní ẹ̀ẹ̀kan ṣoṣo fún ẹni tó bá ní agbára owó àti ara.

Ó jẹ́ ìrìn-àjò tó pàtàkì, ẹ̀yí tí àwọn ipò àti ìran máa ń pamọ́ nínú rẹ̀, àti àwọn ìpìlẹ̀, àwọn ìwọsọ́ àti àwọn dúkìá. Gbogbo kálukú yóò wà nínú aṣọ kan náà, àwọ̀ kan náà, yóò sì máa fi pàápàá àjọṣepọ̀ ènìyàn pẹ̀lú Ọlọ́hun Ọba rẹ̀ hàn: pé: *"Labbaykallāhuma labbayk, labbayka lā sharīka laka labbayk, 'innal-ḥamda wan-ni'mata laka wal-mulk, lā sharīka lak "* (Mo jẹ́ ìpè Rẹ, Ìrẹ Ọlọ́hun, mo jẹ́ ìpè Rẹ. Mo jẹ́ ìpè Rẹ, kò sí orogún fún Ọ, mo jẹ́ ìpè Rẹ. Dájúdájú gbogbo ọpẹ́ àti ẹyìn, ìdẹ̀ra àti ìjọba tì Ẹ̀ ni í ṣe, kò sí orogún fún Ọ́). Ìtumọ̀ ẹ̀yí ni pé: Láti jẹ́ ìpè Rẹ, Ìrẹ Ọlọ́hun Ọba, tí ìjẹ́pè Rẹ míìràn yóò tẹ̀lé e. Ìrẹ Ọlọ́hun Ọba! A wá, tí àwa sì ń fọn rere pẹ̀lú ahọ́n wa, a sì ń fi rinlẹ̀ pẹ̀lú ọkàn wa, pé dájúdájú Ìwọ nìkan ṣoṣo ni O lẹ́tọ̀ọ́ sí ìjọsìn, kò tọ́ sí ẹlòmíràn tó yàtọ̀ sí Ọ, Ìwọ nìkan ni O lẹ́tọ̀ọ́ sí ọpẹ́ àti ẹyìn tó pé,  Ìwọ ni Adẹ́dàá, Ìwọ ni Ó ń ṣe ìdẹ̀ra fún àwọn ẹ̀dá, Ìwọ ni Ọba, kò sí orogún fún Ọ.

*Ḥajj* ṣíṣe jẹ́ ìrìn-àjó tí ó ní í ṣe pẹ̀lú ìgbàgbọ́, Mùsùlùmí yóò máa pààrà níbẹ̀ láàrin àwọn ìṣesí, àwọn iṣẹ́ àti àwọn ọ̀rọ̀ kan, ẹ̀yí tí ó jẹ́ wí pé ohun tí wọ́n gbà lérò pẹ̀lú gbogbo rẹ̀ ni ìrántí Ọlọ́hun àti ìpayà Rẹ̀ àti ṣíṣe àfihàn jíjẹ́ aláìní àti bíbùkáátà sí I, mímọ́ ni fún Un, àti láti wá àforíjìn àti ẹ̀san rere ní ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun. Ànábì Muḥammad – kí  ọlà Ọlọ́hun máa bá a – sọ wí pé: "Ohun tí wọ́n gbé *Ṭawāf* yíká ilé Ọlọ́hun àti pípọ̀sẹ̀sẹ̀ níbi iṣẹ́ *Ḥajj* kalẹ̀ fún ni láti gbé ìrántí Ọlọ́hun dúró" (*Ibn Abī Shaybah*: 15334).



Aṣọ ẹni tí ó gbèrò láti wá sí ìlú *Makkah* láti wá ṣe iṣẹ́ ìjọsìn Ḥajj, lẹ́yìn tí ó bá ti bọ́ aṣọ tí ó bá sáábà, tí ó sì wọ ẹ̀gígé aṣọ méjì, wà fún pípolngo ìtẹ́ríba fún Ọlọ́hun àti ṣíṣe déédé pẹ̀lú gbogbo ẹni tí ó wá, tí ó gba *Ḥajj* ṣíṣe lérò.



# Ẹbí Nínú ẹ̀sìn *Islām*

Òdodo

Òdodo ni ọ̀rọ̀ yìí jẹ́ nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹbí, ní àsìkò tí a wà yìí pé; ó jẹ́ àkójọpọ̀ àwọn ènìyàn kọ̀ọ̀kan, tí àwọn kọ́kọ́rọ́ ọlọ́kan-ò-jọ̀kan wà lọ́wọ́ wọn fún ilé kan ṣoṣo!

Àti pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn ènìyàn, pẹ̀lú ìbànújẹ́, ń sá fún ṣíṣe ògidì ojúṣe rẹ̀ sí ìyàwó àti àwọn ọmọ rẹ̀. Kín ni ohun tí yóò kọ̀ fún un láti gbádún, kí ó sì gbọ́ bùkáátà àwọn adùn rẹ̀ láìgbé ojúṣe yìí?

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pé ìṣesí yìí hàn kedere ní àsìkò yìí, ṣùgbọ́n dájúdájú ó jẹ́ ohun tí ó máa ń wu àwọn ènìyàn kan láti ìbẹ̀rẹ̀ ìtan ọmọnìyàn. Ẹyí, níti pàápàá, sì jẹ́ ìfẹ́ àìmọra fún àǹfààní ti ara ẹni nìkan àti ìmọtara ẹni nìkan burukú, làìwòye sí àwọn àtubọ̀tán rẹ̀ lórí ẹnìkọ̀ọ̀kan àti àwùjọ.

Fún ìdí èyí, ẹ̀sìn *Islām* dé, ó sì dojú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àkàkún rẹ̀ kọ ẹbí yìí, pẹ̀lú ètò rẹ̀, àwọn iwọ̀ rẹ̀ àti àwọn ọranyàn rẹ̀ sí àwọn ènìyàn kọ̀ọ̀kan tí ó wà nínú rẹ̀. Nítorí pé dájúdájú ilé àti ẹbí, nínú ẹ̀sìn *Islām*, ni ààyé àgbọ́ye, ẹ̀kọ́ kíkọ́ àti ìdàgbàsókè. Àti pé mímọ ọ́n, dídára rẹ̀ àti ṣíṣe ojúṣe rẹ̀, ní àwùjọ àti gbogbo ẹbí tí ó wà níbẹ̀ yóò fi dára.


## Kíkanpá mọ́ nǹkan yìí yóò hàn níbi àwọn ìdájọ́ tí kò ní òǹkà, nínú rẹ̀ ni:

1

## Ẹ̀sìn *Islām* kanpá mọ́ ìpìlẹ̀ gbígbé ìyàwó àti kíkó ẹbí jọ:

- Ẹ̀sìn *Islām* ka gbígbé ìyàwó àti kíkó ẹbí jọ sí ara àwọn iṣẹ́ tó pàtàkì jùlọ, àti ara ìlànà àwọn Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun. Nígbà tí apákan nínú àwọn sàábé Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun alápọ̀n-ọ́nlé – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – fẹ́ takú ti mímáa ṣe ìjọsìn, tí wọ́n fẹ́ máa kírun lọ ragbaja, kí wọ́n máa gba ààwẹ̀ àgbàyípo, kí wọ́n sì fi fífẹ́ ìyàwó sílẹ̀, ó sọ fún wọn, ní ẹni tó ń gbà wọ́n níyànjú, pé: "Ṣùgbọ́n èmi máa ń gba ààwẹ̀, mo sì máa ń ṣínu, mo máa ń kírun, mo sì máa ń sùn, mo sì máa ń gbé ìyàwó, nítorí náà ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe ojúkòkòrò kúrò níbi ìlànà mi, kì í ṣe ara mi" (*Al-Bukhārī*: 4776).
- Ó pa àṣẹ pẹ̀lú pé kí á ṣe gbígbé ìyàwò ní ìrọ̀rùn, Ó sì ṣe àdéhùn pẹ̀lú ríran ẹni tí ó fẹ́ gbéyàwó lọ́wọ́, gẹ́gẹ́ bí Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – ti sọ wí pé: "Àwọn mẹ́ta kan ń bẹ, iwọ̀ ni fún Ọlọ́hun láti ràn wọ́n lọ́wọ́" Ó dárúkọ lára wọn: "Àti ẹni tí ó fẹ́ gbéyàwó láti kò ojú ara rẹ̀ ró" (*At-Timidhī:* 1655).
- Nígbà tí *Al-Qur'ān* ń sọ̀rọ̀ nípa àwọn ìdẹ̀ra Ọlọ́hun àti àwọn àmí Rẹ̀, lórí àwọn ọmọ Ànábì Ādam, ó máa ń sọ ní àwọn ìbẹ̀rẹ̀ rẹ̀; ohun tí Ọlọ́hun dá nínú ìfarabalẹ̀, ìfẹ́, àànú àti ìkónimọ́ra láàrin ọkọ àti ìyàwò rẹ̀, gẹ́gẹ́ bí ó ti wà nínú *Al-Qur'ān* pé: **"Àti pé nínú àwọn Àmì Rẹ̀ ni pé; Ó dá àwọn ìyàwó fún yín látara ẹ̀mí ara yín, nítorí kí ẹ le sinmi sí wọn lọ́dọ̀, Ó sì fi ìfẹ́ àti ààánú sí ààrin yín"** (*Ar-Rūm*: 21).
- Ó pa àwọn ọ̀dọ́ ní àṣẹ, nígbà tí okun àti agbára tí ó le koko bá wà lára wọn, láti ṣe ìgbéyàwó. Nítorí ìrọra àti ìfàyàbalẹ̀ tí ó wà níbẹ̀ fún wọn, àti láti wá ọ̀nà àbáyọ tí ó bá ìlànà òfin ẹ̀sìn *Islām* mu sí níní agbára adùn àti ojúkòkòrò wọn.

"Nígbà tí *Al-Qur'ān* ń sọ̀rọ̀ nípa àwọn ìdẹ̀ra Ọlọ́hun àti àwọn àmí Rẹ̀, lórí àwọn ọmọ Ànábì Ādam, ó máa ń mẹ́nu bá a pé ara àwọn àkọ́kọ́ rẹ̀ ni; ohun tí Ọlọ́hun dá nínú ìfarabalẹ̀, ìfẹ́, àànú àti ìkónimọ́ra láàrin ọkọ àti ìyàwò rẹ̀.



## 2

### Ẹ̀sìn *Islām* fún ẹnìkọ̀ọ̀kan nínú ẹbí ní àpọ́nlé tí ó pé, bóyá ó jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin:

Ẹ̀sìn *Islām* gbé ojúṣe tí ó tóbi lórí bàbá àti ìyá nípa rírе àwọn ọmọ wọn. Wọ́n gbà á wá láti ọ̀dọ̀ ‘Abdullāh ọmọ ‘Umar – kí Ọlọ́hun yọ́nú sí àwọn méjèèjì – pé dájúdájú ó gbọ́ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – tí ó ń wí pé: “Gbogbo yín ni adaranjẹ̀, wọn yóò sì bi í léèrè nípa àwọn tí ń dàájẹ̀. Adaranjẹ̀ ni ọkùnrin nínú ẹbí rẹ̀, wọn yóò bi í léèrè nípa àwọn tí ń dàájẹ̀. Adaranjẹ̀ ni obìnrin náà jẹ́ nínú ilé ọkọ rẹ̀, wọn yóò bi í léèrè nípa àwọn tí ń dàájẹ̀. Adaranjẹ̀ ni ọmọ-ọ̀dọ̀ nínú dúkìà ọ̀gà rẹ̀, wọn yóò bi í léèrè nípa ohun tí ń dàájẹ̀” (*Al-Bukhārī:* 853).



## 3

### Ẹ̀sìn *Islām* ṣe ojú kòkòrò lórí fífi ìpìlẹ̀ bíbu ọ̀wọ̀ àti ṣíṣe àpọ́nlé fún àwọn bàbá àti àwọn ìyà wa lélẹ̀, àti jíjígìrì sí ṣíṣe àmójútó wọn, àti títẹ̀lé àṣẹ wọn títí di ọjọ́ ikú:

Bí ọmọkùnrin tàbí ọmọbìnrin ti wulẹ̀ kí ó dàgbà tó, ó pọn dandan fún wọn kí wọ́n máa ṣe àpọ́nlé fún àwọn òbí wọn, kí wọ́n sì máa ṣe dáadáa sí wọn. Ọlọ́hun so èyí mọ́ ṣíṣe ìjọsìn fún Un, mímọ́ ni fún Un, Ó sì kọ̀ nípa títayọ ààlà nínú ọ̀rọ̀ àti iṣe pẹ̀lú àwọn méjèèjì, kódà kí ó jẹ́ pẹ̀lú ṣíṣe àfihàn ọ̀rọ̀ tàbí ohùn tí yóò máa tọ́ka sí mímẹ́ẹ̀rí àwọn méjèèjì. Gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́hun ti sọ nínú *Al-Qur’ān* wí pé: **“Àti pé Ọlọ́hun Ọba rẹ pàṣẹ pé ẹ kò gbọdọ̀ sin ẹnìkankan àyàfi Òun, kí ẹ sì máa ṣe dáadáa sí àwọn òbí méjèèjì. Bóyá ìkan nínú wọn ni ogbó bá ní ọ̀dọ̀ rẹ tàbí àwọn méjèèjì, Má ṣe sọ ọ̀rọ̀ àbùkù sí wọn, má sì ṣe jágbe mọ́ wọn, kí o sì máa sọ̀rọ̀ àpọ́nlé sí wọn”** (*Al-’Isrā’:* 23).



## 4

### Ẹ̀sìn *Islām* pàṣẹ ṣíṣọ́ iwọ̀ àwọn ọmọkùnrin àti àwọn ọmọbìnrin àti jíjẹ́ ọ̀ranyàn ṣíṣe déédé láàrin wọn:

Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – sọ wí pé: “Ó ti tó fún ènìyàn ní ẹ̀ṣẹ̀, kí ó máa rá ẹni tí ń bọ́ láre” (*Abū Dāwūd*: 1692). Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – tún wí, nípa ṣíṣe àmójútó àti nínáwó lórí àwọn ọmọbìnrin níkan pé: “Ẹnikẹ́ni tí ó bá jẹ́ alámójútó fún nǹkankan nínú ọ̀ràn àwọn ọmọbìnrin yìí, tí ò sì ṣe dáadáa sí wọn, wọn yóò jẹ́ gàgá fún un níbi iná” (*Al-Bukhārī*: 5649).

## 5

### Ọlọ́hun ṣe dída ẹbí pọ̀ ní ọ̀ranyàn lórí Mùsùlùmí:

Ìtumọ̀ èyí ni pé: Àjọṣepọ̀ ènìyàn àti ṣíṣe dáadáa rẹ̀ sí àwọn ẹbí rẹ̀ láti ìhà bàbá àti ìyá rẹ̀. Ó sì ka èyí sí ara sísúnmọ́ Ọlọ́hun àti títẹ̀lé àṣẹ rẹ̀. Ó kì wá nílọ̀ nípa yíyẹra fún wọn àti ṣíṣe àìda sí wọn, ó sì ka èyí sí ara àwọn ẹ̀ṣẹ̀ ńláńlá. Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wí pé: “Ẹnikẹ́ni tí ó bá ń já okùnbí kò ní wọ ọgbà-ìdẹra Al-Jannah” (*Muslim*: 2556).



# Ipò obìnrin nínú ẹ̀sìn *Islām*

## Ìwòran

Ìwòran kíákíá lórí àwọn ìkéde nínú àmóhùnmáwòrán, tàbí àwọn àtẹ ìkéde tó wà ní ẹ̀bá ọ̀nà tàbí lára àwọn èèpo àwọn ìwé ìròyìn, yóò jẹ́ ká fura mọ títóbi ọ̀ràn, èyí tí ọ̀lájú mímáa wá ayé lásán dá lórí obìnrin, èyí tó jẹ́ wí pé, ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, wọn kò rí i sí nǹkankan bíkòṣe ohun eré, tàbí ọjà, tàbí ìgbádùn tó wà fún wíwú ìfẹ́ àti adùn jade, àti láti koná èròkérò..

Bóyá èyí kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe ọ̀nà mìíràn tó kéré ní bíba nǹkan lójú jẹ́, ní ìbámu sí ohun tó hàn, ju ohun tí àwọn àwùjọ̀ ìjọ́hun wà lórí rẹ̀ lọ, nínú yíyẹpẹrẹ obìnrin, àti sísọ ọ́ di ohun ìgbádùn àti ọjà tí wọ́n ń tà, tí wọ́n sì ń rà.

Obìnrin, ẹni tó jẹ́ wí pé ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó ń rí ìnira látara àbòsí àti ìrẹ́jẹ, kò gbèrò, láti ipasẹ̀ ìjìjàgbara rẹ̀ láti ìgbà pípẹ́, láti jade kùró ní ọ̀nà tó pa aáyun yìí, kí ó le padà sí ààyè gidi – ṣùgbọ́n láti ọ̀nà tó kéré jùlọ ní ìbani lójú jẹ́ –.

Láti ìgbà tí ẹ̀sìn *Islām* ti dé, síwájú 1400 ọdún, dájúdájú ó gbé ìwọ́de ògidì kalẹ̀ láti tako àwọn ìrẹ́jẹ, èyí tó ti ń ṣe àbòsí fún obìnrin, ó sì gbé kalẹ̀ fún un, nínú àwọn òfin àti àwọn àlàyé ìdájọ́ tó kún, èyí yóò máa ṣọ́ àwọn ìwọ̀ rẹ̀ àti ipò rẹ̀, tí yóò sì máa ṣẹ̀mí pẹ̀lú rẹ̀ ní ẹni iyí, ẹni àpọ́nlé, tí yóò máa jíṣẹ́ rẹ̀, nínú ìṣẹ̀mí-ayé, ní ọ̀nà tó pé jùlọ.


Ìdí nìyí, tí wọ́n fi sọ ọ̀kan nínú àwọn Sūrah *Al-Qur'ān* tó gùn jùlọ ní Sūratun-Nisā', nítorí ohun tó wà níbẹ̀ nínú àwọn ìdájọ́ tó kún rẹ́rẹ́ nípa obìnrin. Ọlọ́hun tún fún wa ní ìró, nínú *Al-Qur'ān*, nípa ìtàn ọ̀kan-ò-jọ̀kan nínú àwọn obìnrin dáadáa. Kódà Ó sọ ọ̀kan nínú àwọn Sūrah, pẹ̀lú orúkọ Maryam ìyá Ànábì ʿĪsā – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –.

Nítorí náà, ẹ̀sìn *Islām* dé láti yí ojú tí wọ́n fi ń wo obìnrin padà, nítoríi kí ó le rí bí Ọlọ́hun Ọba rẹ̀ ti dá a, èèyàn ni, kì í ṣe ọjà, alábàṣe ọjọ́ ìṣẹ̀mí-ayé ni, kì í ṣe alábàṣe òru nìkan, ó sì jẹ́ ìfarabalẹ̀, ìfẹ́, àànú, kì í ṣe adùn, ìgbádùn àti yọ̀tọ̀mí lásán.

## Díẹ̀ nínú àwọn ìdájọ́, èyí tó so mọ́ bíbọ̀wọ̀ fún obìnrin ni ohun tó ń bọ̀ yìí:

- Ó fún obìnrin ní òmìnira láti ṣẹ̀ṣà ọkọ tí ó bá fẹ́. Ó sì gbé ìpín kan tí ó tóbi nínú ojúṣe ríre àwọn ọmọ kọ́ ọ lọ́rùn. Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wí pé: "Adaranjẹ̀ ni obìnrin náà jẹ́ nínú ilé ọkọ rẹ̀, wọn yóò bi í léèrè nípa àwọn tí ń dààjẹ̀" (*Al-Bukhārī*: 853).
- Ó fi orúkọ rẹ̀ sílẹ̀ fún un àti iyì fífi ara rẹ̀ tì sí bàbá rẹ̀, nítorí náà kò ní yí orúkọ rẹ̀ padà lẹ́yìn ìgbeyàwò, ṣùgbọ́n yóò tẹ̀ síwájú pẹ̀lú fífi ara rẹ̀ tì sí bàbá rẹ̀ àti ẹbí rẹ̀.
- Ó kanpá mọ́ iyì àti ọlá tí ń bẹ fún mímáa ṣèkúnlọ́wọ́ fún obìnrin tí ó jẹ́ ọ̀lẹ, tí kò ní ẹnìkankan, kódà kí ó má jẹ́ ara àwọn ẹbí. Ó ṣe wá lójúkòkòrò láti máa ṣèkúnlọ́wọ́ fún un, ó sì ka èyí sí ara àwọn iṣẹ́ tí ó lọ́lá jùlọ ní ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun. Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wí pé: "Ẹni tí ó bá ń náwó lórí obìnrin tí kò ní ọkọ àti táláká dà bíi ẹni tí ó ń jagun sí ojú-ọ̀nà Ọlọ́hun, àti bíi ẹni tí ń dìde kírun ní òru, tí kì í sinmin, tí ń gba ààwẹ̀ ní ọ̀sán, tí kì í ṣínu" (*Al-Bukhārī*: 5661).

> Nígbà tí apákan àwọn gègé ń fi ẹ̀sùn kan ẹ̀sìn *Islām* pẹ̀lú àbòsí fún obìnrin, àti títayọ ààlà lórí àwọn ẹ̀tọ́ rẹ̀, àti àìṣe déédé rẹ̀ – ní ìbámu sí ọ̀rọ̀ ẹnu wọ – pẹ̀lú àwọn ohun tí ayé òde-òni àti ọ̀làjú ń fẹ́, a ó rí i pé 75% nínú àwọn tó ṣẹ̀ṣẹ̀ gba ẹ̀sìn Islām, ní àwọn orílẹ̀dè tó ti dàgbà sókè, bíi Bírítéènì, jẹ́ ara àwọn obìnrin. Pàápàá jùlọ nígbà tí wọ́n kọ́ nípa àwọn ìdájọ́ ẹ̀sìn Islām àti àwọn òfin rẹ̀ nípa àwọn ọ̀ràn ẹbí àti ara ilé! INDEPENDET 6-11-2011



- Ó ṣe déédé láàrin ọkùnrin àti obìnrin níbi àwọn ọlọ́kan-ò-jọ̀kan ọ̀ràn tí ó pọ̀, nínú rẹ̀ ni gbogbo àjọṣepọ̀ tí ó ní í ṣe pẹ̀lú owó, dé bi wí pé Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wí pé: “Àwọn obìnrin ojúgbà àwọn ọkùnrin ni wọ́n jẹ́” (*Abū Dāwūd*: 236)
- Ó ṣe é ní ọ̀ranyàn fún ọkùnrin láti máa tọ́jú rẹ̀ àti láti máa náwó lé e lórí, láìsí ìrègún, tí ó bá jẹ́ wí pé nínú ẹni tí ínáwó lé e lórí ṣe ọ̀ranyàn ni, bíi; ìyàwò, ìyà àti ọmọbìnrin.
- Ẹ̀sìn *Islām* fún obìnrin ní ẹ̀tọ́ rẹ̀ nínú ogún, nínú ìpín tí ó jẹ́ déédé, tí ó ní àpọ́nlé, ó ṣe ọkùnrin ní déédé obìnrin ní àwọn ààyè kan, ìpín rẹ̀ sì yàtọ̀ sí ti ọkùnrin ní àwọn ààyè mìíràn, ní àlékún ni tàbí àdínkú, pẹ̀lú bí sísúnmọ́ òkú rẹ̀ bá ti tó àti àwọn ojúṣe ìnáwó tí ń bẹ lọ́rùn rẹ̀. Nínú wíwo nǹkan ní eréfẹ̀ẹ́ àti ìwòye tó kúrú ni kí ẹnìkan nínú wọn rankankan mọ́ pé ìpín obìnrin dínkù sí ti ọkùnrin ní àwọn ààyè kan, tí kò sì ní bojú, ní ìdàkejì, wo ohun tí Ọlọ́hun ṣe ní ọ̀ranyàn lórí ọkùnrin nínú bùkáátà tó ní í ṣe pẹ̀lú owó níná, bíi nínáwó lórí obìnrin. Nítorí náà *Islām* jẹ́ ẹ̀sìn tó ní ètò, tó ń pé ara wọn, tó sì ní wọ̀tún-wọ̀nsì, apákan nínú rẹ̀ kò le bó òmíràn mọ́lẹ̀.

> Ẹ̀sìn *Islām* fún obìnrin ní ẹ̀tọ́ rẹ̀ nínú ogún, nínú ìpín tí ó jẹ́ déédé, tí ó ní àpọ́nlé, ó ṣe ọkùnrin ní déédé obìnrin ní àwọn ààyè kan, ìpín rẹ̀ sì yàtọ̀ sí ti ọkùnrin ní àwọn ààyè mìíràn, ní àlékún ni tàbí àdínkú.

## Àwọn obìnrin tí ẹ̀sìn *Islām* kanpá mọ́ pípàtàkì wọn:

**Ìyá:** Dájúdájú ọkùnrin kan wá bá Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a –, ó sì wí pé: Ìrẹ Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun! Tani ó ní ẹ̀tọ́ jùlọ kí n máa ṣe dáadáa sí” Ó wí pé: “Ìyá rẹ”. Ọkùnrin náà wí pé: Lẹ́yìn náà tani? Ó wí pé: “Ìyá rẹ”. Ọkùnrin náà wí pé: Lẹ́yìn náà tani? Ó wí pé: “Ìyá rẹ”. Ọkùnrin náà wí pé: Lẹ́yìn náà tani? Ó wí pé: “Bàbá rẹ” (*Al-Bukhārī*: 5626).

**Ọmọbìnrin:** Dájúdájú Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wí pé: “Ẹnikẹ́ni tí ó bá ni ọmọbìnrin mẹ́ta, tí ó ṣe sùúrù lórí wọn, tí ó fún wọn ní oúnjẹ, tí ó fún wọn ní ohun mímu mu, tí ó sì dá aṣọ fún wọn láti inú ìgbìyànjú (owó) rẹ̀, wọn yóò jẹ́ gàgá fún un kúrò níbi iná ní ọjọ́ Ìgbẹ́ndẹ” (*Ibn Mājah*: 3669).

**Ìyàwó:** Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wí pé: “Ẹni tí ó dára jùlọ nínú yín ni ẹni tí ó dára jùlọ nínú yín sí àwọn ara ilé rẹ̀, èmí ni mo sì dára jù yín lọ sí àwọn ara ilé mi” (*At-Tirmidhī*: 3895).





> Àjọṣepọ̀ ọkùnrin àti obìnrin, nínú ẹ̀sìn *Islām*, àjọṣepọ̀ tí ń pé ara wọn ni, kì í ṣe ìjà. Nítorí náà kálukú wọn yóò máa dí ibi tí ìkejì kù sí níbi ṣíṣe àgbékalẹ̀ àwùjọ Mùsùlùmí.

## Kò sí ààyè fún ìjà láàrin ìran méjèèjì nínú ẹ̀sìn *Islām*:

Nínú ẹ̀sìn *Islām*, kò sí ogun àti ìjà láàrin ìran méjèèjì. Kò sì sí ìtumọ̀ fún ìfànfà lórí àwọn ọ̀rọ̀ ayé. Kò sí ààyè fún líle mọ́ obìnrin tàbí le mọ́ ọkùnrin àti ìgbìyànjú láti fi ìyà jẹ ẹnìkan nínú àwọn méjèèjì, bíbú u àti mímáa wá àwọn àléébù rẹ̀!

Báwo ni ènìyàn yóò ṣe máa gbógun ti ìlàjì rẹ̀, báwo ni ẹ̀gbọ́n àti àbúrò, tó jẹ́ ọmọ ìyá, ọmọ bàbá kan náà, yóò ṣe máa bá ara wọn jà? Nítorí náà obìnrin, gẹ́gẹ́ bí Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun alápọ̀n-ọ́nlé ti sọ jẹ́ ojúgbà fún ọkùnrin àti ìlàjì rẹ̀ keji. Àjọṣepọ̀ tó wà láàrin àwọn méjèèjì, ó ń pé ara wọn ni, ọ̀kọ̀ọ̀kan nínú àwọn méjèèjì, yóò máa dí àbùjẹ́kù ẹnìkejì láti mọ àwùjọ Mùsùlùmí.

Ó ní ẹ̀tọ́ fún ọkùnrin láti wò ó àti gbígbádùn ìyàwó rẹ̀ bí ó bá ti fẹ́, èyí sì ní ẹ̀tọ́ fún obìnrin náà pẹ̀lú ọkọ rẹ̀. Dájúdájú Ọlọ́hun pe ọkọ ní aṣọ ìbora fún ìyàwó rẹ̀, Ó sì pe ìyàwó náà ní aṣọ ìbora fún ọkọ rẹ̀, gẹ́gẹ́ bíi àwòrán tí ó rẹwà nípa àsopọ̀ ẹ̀mí, ìrọ̀rí àti ara láàrin àwọn méjèèjì. Ó wí pé: **“Aṣọ ìbora ni wọ́n jẹ́ fún yín, ẹ̀yin náà sì jẹ́ aṣọ ìbora fún wọn”** (*Al-Baqarah*: 187)

Ohun tí ọkùnrin máa ń rí, fún ìgbà àkọ́kọ́, ní ìjẹ́-ọ̀lẹ lára obìnrin, kò jẹ́ nǹkankan bíkòṣe ọ̀nà mìíràn fún ìran kan nínú agbára, èyí tí ọkùnrin kò yanjú níbẹ̀, tí kò sì ní ìkápá rẹ̀, ṣùgbọ́n ẹbí bùkáátà sí i.. Ohun tí òun náà sí ń rí bíi àbùkù lára ọkùnrin, ó le jẹ́ àfihàn fún àwọn agbára, èyí tí kò bá òun mu, ṣùgbọ́n ìṣẹ̀mí-ayé àti àwùjọ kò le dúró tọ́ láìsí i..

Nínú erémọ̀dé, ní kí á ní Ọlọ́hun dá ènìyàn ní méji (àwọn ọkùnrin àti àwọn obìnrin), lẹ́yìn náà kí á wá wí pé: Ọ̀ranyàn ni kí ìran méjèèjì ṣe déédé níbi gbogbo nǹkan.

Nígbà tí apákan nínú àwọn ọkùnrin ń rankàn ohun tí Ọlọ́hun fún àwọn obìnrin, nínú àwọn ẹ̀tọ́, tí apákan nínú àwọn obìnrin náà sì rankàn ohun tí Ọlọ́hun fún àwọn ọkùnrin, nínú àwọn ẹ̀tọ́, àwọn āyah kan sọ̀kalẹ̀, nínú *Al-Qur’ān* alápọ̀n-ọ́nlé tó ń sọ wí pé: **“Àti pé ẹ má ṣe máa rankàn ohun tí Ọlọ́hun fi gbé ọlá fún apákan yín lórí apákejì. Àwọn ọkùnrin ní ìpín nínú ohun tí wọ́n ṣe, àwọn obìnrin náà sì ní ìpín nínú ohun tí wọ́n ṣe, ẹ sì bẹ̀ẹ̀rè lọ́wọ́ Ọlọ́hun nínú Ọlá Rẹ̀”** (*An-Nisā’*: 32). Nítorí náà kálukú ni ó ní àwọn ohun ẹ̀ṣà ti ẹ̀, ìṣẹ́ ti ẹ̀ àti ohun tí Ọlọ́hun fi ṣe àpọ́nlé rẹ̀. Kálukú náà sì ni ó ń ṣe àpàntètè lọ síbi Ọlá Ọlọ́hun àti ìyọ́nú Rẹ̀. Òfin ẹ̀sìn Ọlọ́hun kò sì wá fún ọkùnrin nìkan tàbí obìnrin níkan, ṣùgbọ́n ó wá fún gbogbo ènìyàn àti fún àwùjọ Mùsùlùmí.




## Àjọṣepọ̀ láàrin ọkùnrin àti obìnrin:

Fífi ètó àti òǹdè sí àjọṣepọ̀ láàrin ọkùnrin àti obìnrin, ní abẹ àwọn ààlà, àwọn òfin, àwọn àláádà àti àwọn ìhùwàsí tó ń ṣètò rẹ̀, nínú ohun tí àwọn ìgbìyànjú àti àwọn ohun tí ènìyàn kọ̀ọ̀kan ṣà ní ẹ̀ṣà yapa ara níbẹ̀ ni, láti ìgbà dégbà. Ní ohun tó nira láti ṣe àkótán rẹ̀ tàbí ṣe àwárí rẹ̀. Ṣùgbọ́n ìwé ìtàn àti ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ nípa ènìyàn ń sọ fún wa nípa àwọn ènìyàn kan tí wọn kò rí i pé aburú kankan wà níbi wíwà ní ìhòhò pọnbele, lílọgun ìran jìran, èyí tó le koko fún ìran méjèèji, títí kan àwọn ìjọ ènìyàn mìíràn tí wọ́n máa ń de obìnrin mọ́ irin, nítorí pé wọ́n ń bẹ̀rù lé e lórí, títí kan àwọn mìíràn tí wọ́n máa ń bo àwọn ọkùnrin yàtọ̀ sí àwọn obìnrin tàbí wọ́n fi ẹ̀sùn kàn wọ́n pé wọ́n ń bo àwọn apákan nínú ara yàtọ̀ sí òmíràn, àti àwọn nǹkan mìíràn tí a kò le sọ ọ́ tán..

Àwọn ìran ènìyàn tó pọ̀ jùlọ, láti ìgbà dégbà – pàápàá jùlọ ẹni tó bá ní ìwọ̀nba díẹ̀ nínú ọ̀làjú nínú wọn – máa ń rí i pé àjọṣepọ̀ láàrin ọkùnrin àti obìnrin bùkáátà sí ètò àti òfin tí yóò máa darí rẹ̀, nítorí kí ìṣẹ̀mí-ayé má yípadà lọ sí abúlé tàbí ìgbèkùn, èyí tí gbogbo ìyàtọ̀ tó wà láàrin ènìyàn àti ẹranko yóò roko ìgbàgbé nínú rẹ̀.

## Irú àjọṣepọ̀ tó wà láàrin ọkùnrin àti obìnrin nínú ẹ̀sìn *Islām*:

Àjọṣepọ̀ ọkùnrin pẹ̀lú obìnrin, nínú ẹ̀sìn *Islām*, kì í ṣe ìgbìyànjú ènìyàn, èyí tí wọ́n ti fi ààlà sí pẹ̀lú àwọn irinṣẹ́ ìtàn àti ìmọ̀ ojú-ọjọ́, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ètò tó ń gbé ara wọn nígbọ̀wọ́, tó bá gbogbo àsìkò àti ààyè mu. Ọlọ́hun sọ ọ́ kalẹ̀ nínú *Al-Qur'ān* alápọ̀n-ọ́nlé, Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun alápọ̀n-ọ́nlé, Muḥammad – kí ọla Ọlọ́hun máa bá a – sì kọ́ àwọn ènìyàn nípa rẹ̀.

Àjọṣepọ̀ yìí, irú rẹ̀ àti àwọn ààlà rẹ̀ máa ń yàtọ̀ sí ara wọn, ní ìbámu sí ipò tí obìnrin wà sí ọkùnrin, gẹ́gẹ́ bí ẹ̀sìn *Islām* ti ṣe àlàyé rẹ̀.

## Àwọn ọkùnrin sí obìnrin, nínú ẹ̀sìn Islām, pín sí oríṣirísi:

**1. Kí ó jẹ́ wí pé ọkùnrin náà ni ọkọ rẹ̀:**

Kó sì ohun tó tọ́ka jùlọ, tó sì dé ògóngó jùlọ lórí àjọṣepọ̀ yìí láàrin ọkọ àti ìyàwó ju bí *Al-Qur'ān* ti ròyìn rẹ̀ lọ. Dájúdájú Ọlọ́hun pe ọkọ ní aṣọ ìbora fún ìyàwó rẹ̀, Ó sì pe ìyàwó náà ní aṣọ ìbora fún ọkọ rẹ̀, gẹ́gẹ́ bíi àwòrán tí ó rẹwà nípa àsopọ̀ ẹ̀mí, ìròrí àti ara láàrin àwọn méjèèjì. Ó wí pé: **"Aṣọ ìbora ni wọ́n jẹ fún yín, ẹ̀yin náà sì jẹ́ aṣọ ìbora fún wọn"** (*Al-Baqarah:* 187)

**2. Kí ó jẹ́ ara àwọn eléèwọ̀ rẹ̀:**

Ohun tí a gbà lérò pẹ̀lú àwọn eléèwọ̀ ni gbogbo ẹni tí ó jẹ́ èèwọ̀ fún obìnrin láti fẹ́ ní ìyàwó, ní jíjẹ́ èèwọ̀ láéláé, nítorí jíjẹ́ ẹbí tí ó súnmọ̀ pẹ́kípẹ́kí, wọ́n jẹ́ 13 nínú àwọn ọkùnrin tí wọ́n jẹ́ alásúnmọ́, bíi bàbá, baba-baba, ọmọ, arákùnrin, arákùnrin bàbá, arákùnrin ìyá, ọmọ arákùnrin tàbí ti arábìnrin, ọmọ ọmọkùnrin tàbí ti ọmọbìnrin, àti ohun tí ó yàtọ̀ sí èyí.. Obìnrin yóò máa hàn níwájú àwọn alásúnmọ́ rẹ̀, tí wọ́n jẹ́ eléèwọ̀ fún un làìwọ ḥijāb tí ó bo gbogbo ara rẹ̀ tán, ṣùgbọ́n pẹ̀lú àdámọ̀ rẹ̀ láìsí ní ìhòhò.

**3. Kí ọkùnrin náà jẹ́ àjòjì sí i:**

Ohun tí a gbà lérò pẹ̀lú ọkùnrin àjòjì ni: Gbogbo ọkùnrin tí kò sí lára àwọn eléèwọ̀ rẹ̀.

Dájúdájú ẹ̀sìn *Islām* ṣe àgbékalẹ̀ àwọn òndè àti àwọn òfin, èyí tí yóò máa darí àjọṣepọ̀ ọkùnrin pẹ̀lú obìnrin tí ó jẹ́ àjòjì sí i, láti fi ṣọ́ ọmọlúàbí rẹ̀ àti láti dí àwọn ọ̀nà tí èṣù máa ń gbà wọlé tọ ènìyàn. Àti pé Ẹni tí Ó dá ènìyàn ni Ó mọ jùlọ nípa ohun tí ó dára fún un. gẹ́gẹ́ bí ó ti wá nínú *Al-Qur'ān* pé: **"Ṣe Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá kò wa ní mọ̀ bí? Àti pé Òun ni Aláàánú, Arínúróde"** (*Al-Mulk*: 14).

### Kílódé tí ẹ̀sìn *Islām* ṣe wíwọ *ḥijāb* níwájú àwọn ọkùnrin àjòjì ní òfin?

- Kí ó le rọrùn fún obìnrin láti jẹ́ iṣẹ́ tí Ọlọ́hun rán an nínú ìṣẹ̀mí-ayé àti àwùjọ ní àwọn agbegbe ìmọ̀ àti iṣẹ́ ní ọ̀nà tí ó dára jùlọ pẹ̀lú ṣíṣọ́ àpọ́nlé àti níní àmójúnú rẹ̀
- Dídín àti fífúyẹ́ àwọn ọ̀nà anù àti wíwú ìfẹ́ adùn jade kù, láti ṣọ́ mímọ́ àwùjọ, ní ọ̀nà kan, àti láti ṣọ́ àpọ́nlé obìnrin, ní ọ̀nà kejì.
- Ríran àwọn ọkùnrin tí ń wo obìnrin lọ́wọ́ lórí ìkójúró àti ìkóra ẹni ní ìjánu. Nítorí náà wọn yóò máa lò bíi ènìyàn tí òun náà yóò máa gbádùn irú ohun tí wọ́n ń gbádùn nínú àwọn ipò ọ̀lájú àti ìmọ̀, kì í ṣe bíi ẹni tí ó jẹ́ àkójọpọ̀ ohun tí ó máa ń wú àdámọ́ ìfẹ́ adùn jáde àti irinṣẹ́ eré àti ìgbádùn lásán.



## Àwọn òndè tó wà fún àjọṣepọ̀ láàrin ọkùnrin àti obìnrin àjòjì:

**1. Ríre ojú nílẹ̀:**

Ọlọ́hun pa ìran ènìyàn méjèèjì lápapọ̀, láṣẹ pẹ̀lú ríre ojú nílẹ̀; èyí tí ó túmọ̀ sí mímá máa wo ohun tí ó le wú àdámọ́ fífẹ́ adún síta, nítorí pé dájúdájú ó jẹ́ ọ̀nà ìkójúró àti ṣíṣọ́ àwọn ọmọlúàbí ènìyàn, gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ wí pé títẹjú mọ́ nǹkan láìní ààlà jẹ́ ọ̀nà àwọn ẹ̀ṣẹ̀ àti àwọn ìwà ìbàjẹ́, gẹ́gẹ́ bí ó ti wà nínú *Al-Qur'ān* pé: **"Sọ fún àwọn olùgbàgbọ́ òdodo lọ́kùnrin pé kí wọ́n máa rẹ ojú wọn nílẹ̀, kí wọ́n sì máa ṣọ́ abẹ́ wọn. Ìyẹn ni ó mọ́ jùlọ fún wọn. Dájúdájú Ọlọ́hun jẹ́ Arínúróde pẹ̀lú gbogbo ohun tí wọ́n ń ṣe • Àti pé kí o sọ fún àwọn olùgbàgbọ́ òdodo lóbìnrin pé kí wọ́n máa rẹ ojú wọn nílẹ̀, kí wọ́n sì máa ṣọ́ abẹ́ wọn"** (*An-Nūr:* 30-31).

**2. Bíbá ara ẹni ṣe pẹ̀lú ẹ̀kọ́ àti ìwà rere:**

Nítorí náà ọkùnrin yóò máa bá obìnrin lò, níbi àwọn ọ̀ràn iṣẹ́ tàbí ẹ̀kọ́ tàbí ohun tó yàtọ̀ sí èyí, pẹ̀lú ẹ̀kọ́ àti àpọ́nlé, pẹ̀lú jíjìnnà sí gbogbo ohun tí ó le wú àwọn àdámọ́ adùn jáde ní ọ̀nà kọ̀nà tó le jẹ́.

**3. Wíwọ *ḥijāb*:**

Ọlọ́hun ṣe wíwọ *ḥijāb* ní ọ̀ranyàn lórí obìnrin yàtọ̀ sí ọkùnrin, nítorí ohun tí Ó dá sí i lára nínú àwọn àmì ẹwà, àti àwọn ohun tí ó le wú fífẹ́ adùn jáde, nínú ohun tí ó le jẹ́ kí ó jẹ́ àdánwò fún ọkùnrin ju kí ọkùnrin jẹ́ àdánwò fún un lọ. Ìdí nìyí, tí a ó fi rí i pé ohun tó pọ̀ jùlọ nínú ìtàn àtijọ́ títí dé àsìkò wa yìí, ni kí wọ́n máa lo obìnrin fún ìgbádùn ọkùnrin, kì í ṣe ìdàkejì. Èyí ni ohun tí à rí, tó hàn kedere fún gbogbo ojú láti rí i nínú àwọn ilé àti ìwé ìròyìn ọlọ́kan-ò-jọ̀kan ní ayé òde-òní.

Ààlà *ḥijāb* wíwọ̀ nínú ẹ̀sìn Islām ni kí obìnrin bo gbogbo ara rẹ̀ àyàfi ojú rẹ̀ àti àtẹ́lẹwọ́ rẹ̀ méjèèjì, níwájú àwọn ọkùnrin tí ó jẹ́ àjòjì sí i, gẹ́gẹ́ bí *Al-Qur'ān* ti pàṣẹ pé: **"Àti pé kí wọ́n má ṣe fi ọ̀ṣọ́ wọn hàn àyàfi èyí tí ó bá hàn nínú rẹ̀"** (*An-Nūr:* 31).



Ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn ẹni tí ó máa ń ṣe àtakò lílo *ḥijāb* obìnrin nínú ẹ̀sìn Islām máa ń ṣe bíi ẹni pé wọn kò mọ̀ pé àwòrán obìnrin tí ó pàtàkì jùlọ, nínú ìtàn, gẹ́gẹ́ bí ó ti wà nínú àwọn àwòrán Maryam, tí ó jẹ́ wúńdíá, kì í hàn àyàfi pẹ̀lú *ḥijāb*. Ohun tí ó sì jọ jùlọ ni *ḥijāb* àwọn Mùsùlùmí.



# Òfin ẹ̀sìn *Islām* nípa oúnjẹ jíjẹ àti nǹkan mímu

Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, ohun tó máa ń jẹ́ ìbéèrè àkọ́kọ́, èyí tí ẹni tó fẹ́ wádìí nípa ẹ̀sìn *Islām* mán ń bèèrè ni pé: Kílódé tí wọ́n ń ṣe àwọn ọtí àti àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn àti ẹlẹ́dẹ̀ ní èèwọ̀?

Láti fèsì sí èyí, ó pọn dandan kí á ṣe àlàyé pàtàkì yìí:

*Al-Qur'ān* ṣe gbogbo ohun tí ń bẹ lórí ilẹ̀ ní ẹ̀tọ́ fún àwọn Mùsùlùmí láti máa fi ṣe ànfààní. Dájúdájú ọ̀rọ̀ wá sàn án, nípa rẹ̀ nínú *Al-Qur'ān* pé dájúdájú, Ó dá gbogbo ohun tí ń bẹ lórí ilẹ̀ fún wa, nítorí kí á le máa fi ṣe ànfààní: **"Òun ni Ẹni tí Ó dá gbogbo ohun tí ń bẹ lórí ilẹ̀ pátápátá fún yín"** (*Al-Baqarah*: 29).

Nínú èyí ni oúnjẹ àti nǹkan mímu, ẹ̀tọ́ ni gbogbo rẹ̀ àyàfi ohun tí wọ́n bá ṣe àyàfi rẹ̀ nínú *Al-Qur'ān* nítorí pé ó jẹ́ ẹ̀gbin àti pé ó le kó ìnira bá àlááfíà ènìyàn tàbí kí ó mú làákàyè rẹ̀ lọ. Bóyá ó pàtàkì sí ẹ kí o mọ̀ nípa jíjẹ́ èèwọ̀ ẹlẹ́dẹ̀ jíjẹ àti ọtí mímu.

## Ẹlẹ́dẹ̀:

Ṣíṣe jíjẹ ẹlẹ́dẹ̀ ní èèwọ̀ wá nínú *Al-Qur'ān* ní ọ̀nà tí ó lọ sàn án, pẹ̀lú pé ẹlẹ́dẹ̀ kì í ṣe ẹranko tí àwọn Lárúbáwá mọ̀ nígbà náà. Ṣíṣe jíjẹ ẹ́ ní èèwọ̀ yìí jẹ́ ohun tí ó ya apákan nínú àwọn ènìyàn lẹ́nu, ó sì máa ń takò ó, pẹ̀lú pé èyí kì í ṣe ohun tí ó ní í ṣe pẹ̀lú àwọn Mùsùlùmí nìkan, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ohun tí wọ́n ṣe ní èèwọ̀ ní ọ̀dọ̀ àwọn Yàhúúdí bákan náà, gẹ́gẹ́ bí èyí ti jẹ́ ohun tí a ti mọ̀ tẹ́lẹ̀. Àwọn ọ̀rọ̀ tí ó wá lórí èyí hàn kedere nínú Májẹ̀mu àtijọ́. Ṣùgbọ́n ohun tí ó yẹ kí ó fa ìyàlẹ́nu ni pé dájúdájú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímímọ̀ nípa ẹ̀sìn fi rinlẹ̀ pé dájúdájú jíjẹ ẹlẹ́dẹ̀ jẹ́ ohun tí wọ́n ṣe ní èèwọ̀ ní ọ̀dọ̀ àwọn Kìrìsìtẹ́nì, pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ tí ó fojú hàn nínú Májẹ̀mu titun. Ṣùgbọ́n ìyípadà àti pàsípààrọ̀ ti bá a lẹ́yìn èyí. Wo: (Bíbélì *Saint Mark* 5/11-13, *Mathew* 67, ìwé ìhìnrere *Peter* kejì 2/22, *Luke* 15/11).

Kín ni ohun tí ó burú, níbi kí Ọlọ́hun dán wa wò pẹ̀lú kíkọ jíjẹ àwọn oúnjẹ kan lẹ́yìn tí Ó ti ṣe jíjẹ èyí tí ó pọ̀ jùlọ nínú rẹ̀ ní ẹ̀tọ́ fún wa; nítorí kí Ó le dán ìgbàgbọ́ wa àti títẹ̀lé àṣẹ Rẹ̀ wa wò, gẹ́gẹ́ bí Ó ti dán Ànábì Ādam – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – wò, lẹ́yìn tí Ó ti ṣe jíjẹ àwọn ohun tí ó mọ́ nínú ọgbà-ìdẹ̀ra *Al-Jannah* ní ẹ̀tọ́ fún un pẹ̀lú ṣíṣe jíjẹ lára igi kan pàtó ní èèwọ̀ fún un?





## Àwọn ọtí àti àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn:

A ka; gbígbógun tí àwọn àjàkálẹ̀ àrùn àti àwọn àìsàn, èyí tó máa ń kó ìparun bá ìṣẹ̀mí-ayé àwọn ènìyàn, àti gbígbé àwọn òfin àti àwọn ètò tó fidí múlẹ̀ kalẹ̀ láti ṣọ́ àlááfíà àwọn ènìyàn àti ìṣẹ̀mí-ayé wọn, sí ara àwọn ojúṣe àwọn orílẹ̀-èdè àti àwọn ìjọba tó pàtàkì jùlọ, èyíkéyìí ààyẹ tó bá bá a, yóò ṣẹ́rí padà wá bá ẹnikọ̀ọ̀kan àti àwujọ pẹ̀lú àwọn orípa tí kò dára jùlọ, tó sì burúkú jùlọ.


Bóyá ohun tí mímọ̀ nípa rẹ̀ yóò bá gbogbo wa ní òjijì ní pé dájúdájú, ní ìbámu sí àwọn ìwádìí tó ṣe gbára lé, gẹ́gẹ́ bí àwọn àbájáde ìjokòó ìgbìmọ̀ tó wà fún àlááfíà gbogbo àgbáyé, àti iṣẹ́- ìwádìí, èyí tí Yunifásítì Oxford ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀, èyí tí wọ́n tẹ̀ jáde nínú ìwé-ìròyìn Nature 483, (15, osù kẹta, 2012) 275, àti àbájáde ìjokòó ìgbìmọ̀ tó wà fún àlááfíà gbogbo àgbáyé 11/2/2011. Dájúdájú òǹkà àwọn tí ọtí ń dá ẹ̀mí wọn légbodò, ní ọdọọdún, pọ̀ ju òǹkà àwọn tí àìsàn Éèdì, ibà àti ikọ́ fée lápapọ̀ ń gba ẹ̀mí wọn lọ, ó sì fẹ́ẹ̀ tó ìlọ́po mẹ́ta àwọn tí gbogbo ogun, pípa ẹ̀yà kan run nípakúpa, àti ìwà sùnmọ̀mí, dá ẹ̀mí wọn légbodò, ní ọdún kan náà lọ. Ka apákan nínú àwọn òǹkà, èyí tí iṣẹ́-ìwádìí pẹ̀lú àwọn àbájáde ìjokòó ìgbìmọ̀ tó wà fún àlááfíà gbogbo àgbáyé fi rinlẹ̀.



**Àwọn tí ọtí àti àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn ń ṣe okùnfà ikú wọn,** ní ọdọọdún, pọ̀ ju mílíọ̀nù méjì àti ààbọ̀ lọ. Nínú wọn ni 320,000 ọ̀dọ́, tí wọ́n jẹ́ ọmọ ọdún 15-29. Wọ́n ń gba ẹ̀mí ara wọn, ní ọdọọdún, ní gbogbo àgbáyé, nítorí àwọn okùnfà tó ní í ṣe pẹ̀lú mímu àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn. Èyí sì jẹ́ 9% nínú àpapọ̀ gbogbo ikú tó ń wáyé ní ọdún, èyí tí wọ́n kọ sílẹ̀ láàrin àwọn tí ọjọ́ orí wọn kò jù báyìí lọ.




Iṣẹ́-ìwadìí tó wáyé ní ìlú Amẹ́ríkà fi hàn pé dájúdájú **700,000 ọmọ-akẹ́kọ̀ọ́ Yunifásítì**, ní ọdọọdún máa ń kojú àkọlù ipa láti ọ̀dọ̀ àwọn ọmọ-akẹ́kọ̀ọ́ tí wọ́n ti mu àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn yó.




Àbájáde tí àlàyé rẹ̀ kún, ní ọdún 2001, fi hàn pé dájúdájú **80% nínú àwọn ìwá-ọ̀daràn** àfipádá, èyí tó wáyé láti ọwọ́ àwọn ọ̀dọ́ ní ìlú Ustūniyā, dájúdájú wọ́n so ó mọ́ àṣejù níbi mímu àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn.

**Wọ́n** ka àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn, sí ohun tó ń fa ìlàrin ìpàniyàn tó ń ṣẹlẹ̀ lórí ilẹ̀ ayé.


**Gbogbo àwọn àlàyé àti àbájáde ìgbìmọ̀ tó wà fún àláàfíà gbogbo àgbáyé,** ń pe gbogbo orílẹ̀-èdè sí ṣíṣe àwọn ètò àti àwọn òfin tó lọ sàn án, èyí tí yóò mú àdínkùn, tàbí fi òpin sí àwọn ìbànújẹ́ ojoomọ́ yìí, èyí tí mímu àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn ń ṣe sábàbí rẹ̀.

## Ní ọdún kan, ní ìlú Bírítéènì nìkan ṣoṣo:

- Ohun tó fẹ́ẹ̀ tó mílíọ̀nù kan ìwá-ọ̀daràn àfipádá, èyí tó so mọ́ mímu àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn, wáyé níbẹ̀. Wọ́n sì rí i, níti pàápàá, pé ìlàjì àwọn ìwá-ọ̀daràn àfipádá, ní àpapọ̀, máa ń so mọ́ mímu àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn, nínú ìwòye àwọn tí ó máa ń bá a lọ.
- Ohun tó súnmọ́ 7 mílíọ̀nù gbígba aláìsàn sí ààyè ìṣẹ̀lẹ̀ òjijì ní àwọn ilé ìwòsàn máa ń so mọ́ mímu àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn, èyí tí ìnáwó rẹ̀ máa ń súnmọ́ 650 mílíọ̀nù ojúlówó pọ́nùn ìlú Bírítéènì, ní ọdún kan, lórí ẹni tí yóò san àwọn ìtaràn...
- Wọ́n ṣe òduwọn àpapọ̀ àwọn ìnàwó lórí ìwá-ọ̀daràn, àti dídá wàhálà sílẹ̀, èyí tó so mọ́ mímu àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn, èyí tó wà lọ́rùn àwọn tí yóò san àwọn ìtaràn, wà láàrin 8 sí 13 mílíọ̀nù ojúlówó pọ́nùn ìlú Bírítéènì, ní ọdọọdún.



## Báwo ni *Al-Qur'ān* ti bá mímu àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn àti ọtí lò?




Ẹ̀sìn *Islām* kò dúró de àwọn àbájáde ìjokòó ìgbìmọ̀ tó wà fún àláàfíà gbogbo àgbáyé, kó tó ṣe àwárí ipa burúkú tí mímu àwọn ohun tí ó máa ń pa ènìyàn lórí ẹnikọ̀ọ̀kan àti àwùjọ.. Nítorí pé Ẹni tó dá ènìyàn, Òun ni Onímímọ̀ nípa ohun tí yóò tún ìṣẹ̀mí rẹ̀ àti àwùjọ rẹ̀ ṣe.

Dájúdájú ẹ̀sìn *Islām* dé wá bá àwọn Lárúbáwá, tó sì jẹ́ wí pé, ní ìgbà náà, wọ́n kò le jáwọ́ níbi íhúnrìrà àti mímu nǹkan. Àwọn ọtí, pẹ̀lú gbogbo ìran rẹ̀, òun ni ìgbádùn wọn tó tóbi jùlọ, tó sì níye lórí jùlọ.. Òun ni wọ́n máa ń fi ṣe fáàrí sí ara wọn, orí rẹ̀ ni wọ́n sì máa ń ná gbogbo owó tí wọ́n bá ní lọ́wọ́ lé.

*Al-Qur'ān* bá ọ̀ràn yìí lò ní ọ̀nà tí ó dé ògóngó níbi gbígbé ọ̀rọ̀ kalẹ̀ àti déédé, nígbà tí ó fi àwọn ànfààní àti ìwúlò kan rinlẹ̀ fún ọtí. Nítorí pé ẹni tí ó ń mu ún le rí ìgbádùn àti ìrọ̀rà tí ó ní ìgbà, èyí tí yóò mú ìbànújẹ́ àti ìrònú rẹ̀ lọ.. Ṣùgbọ́n orípa èyí àti àtubọ̀tán rẹ̀ burúkú jáì. Kò sì sí ìwòsàn fún àwọn orípa rẹ̀ àti àwọn àtubọ̀tán rẹ̀ nínú ẹ̀mí, ìhùwàsí àti àláàfíà lórí ẹnikọ̀ọ̀kan àti àwùjọ, gẹ́gẹ́ bí ó ti wà nínú *Al-Qur'ān* pé: **"Wọ́n ń bi ọ́ léèrè nípa (ìdàjọ́) ọtí àti tẹ́tẹ́, wí pé: Ẹ̀ṣẹ̀ tí ó tóbi ń bẹ nínú àwọn méjèèjì àti àwọn ànfààní fún àwọn ènìyàn, ṣùgbọ́n ẹ̀ṣẹ̀ àwọn méjèèjì tóbi ju ànfààní wọn lọ"** (*Al-Baqarah:* 219).

Lẹ́yìn náà kíkanpá mọ́ kíkọ̀ nípa rẹ̀ dé, àti kíkà á sí ara iṣẹ́ ẹ̀ṣù, èyí tí ó máa ń fa ọ̀tá, mímáa bínú ara ẹni àti mímáa ṣẹ́rí ènìyàn kúrò níbi àwọn nǹkan gíga àti èyí tó pàtàkì. Wọ́n bi àwọn ènìyàn léèrè, nínú *Al-Qur'ān* pé: (Ṣe ẹ̀yin yóò wá fi òpin sí i bí?). Àwọn ènìyàn sì dáhùn pé: A ti jáwọ́.. A ti jáwọ́. Wọ́n sí yí àwọn ọtí dá sí àwọn ojú-ọ̀nà ìlú *Madīnah*, tó jẹ́ ìlú Ànábì, láti juwọ́ sílẹ̀ fún àṣẹ Ọlọ́hun nínú *Al-Qur'ān.*




# Ẹ̀ṣẹ̀ àti ìrònúpìwàdà

## Ìròrí

Ìròrí ṣíṣe àṣìṣe àti déédé jẹ́ ohun tí a le kà sí ọ̀kan nínú àwọn wàhálà ìròrí tó pàtàkì jùlọ nínú àwọn ẹ̀sìn àti àwọn àdìsọ́kàn kan, àwọn àdìsọ́kàn yìí máa ń yàtọ̀ láàrin ara wọn níbi ọ̀nà tí wọ́n máa ń gbà bá àṣìṣe àti ẹ̀ṣẹ̀ lò, àti ìrònúpìwàdà àti àbámọ̀.

Ẹ̀sìn *Islām* ń wòye, pẹ̀lú òṣùnwọ̀n tí ó jindó, sí àdámọ̀ ènìyàn, èyí tí Ọlọ́hun dá, tí Ó sì dá àwọn ohun tí ó máa ń ti ènìyàn lọ síbi dáadáa àti aburú mọ́ ọn. Òun kò bá a lò pẹ̀lú pé kí ó kà á sí ọ̀kan nínú àwọn *Malā'ikah*, tí wọ́n dá lórí ṣíṣe dáadáa nìkan. Nítorí náà ó fi rinlẹ̀ pé dájúdájú gbogbo ọmọ Ādam ni aláṣìṣe, ṣùgbọ́n ní ọ̀nà mìíràn, ó tún gbé kọ́ ọ̀ lọ́rùn pé òun ni yóò dáhùn fún àwọn ohun tí ó bá ṣe àti àwọn ohun tí ó bá ṣà lẹ́ṣà. Níbi ni àlàyé ìròrí ẹ̀sìn *Islām* nípa ẹ̀ṣẹ̀ dídá àti ìrònúpìwàdà yóò ti wáyé, èyí tí a le sọ ní ṣókí nínú ohun tí ń bọ̀ yìí:

- Àkọ́kọ́ ohun tí a ó bá pàdé nínú *Al-Qur'ān* nípé dájúdájú ẹ̀ṣẹ̀ jẹ́ àdádá, nígbà tí ìrònúpìwàdà náà jẹ́ àdáṣe, pẹ̀lú ìwòye tí ó hàn kedere, tí ó sì rọrùn, tí kò sí ìtakókó àti ìrújú nínú rẹ̀. Kò sí ẹ̀ṣẹ̀ kankan tí wọ́n ti dá bọ ènìyàn lọ́rùn síwájú kí wọ́n tó bí i. Ṣùgbọ́n gbogbo ènìyàn ni wọ́n bí ní ẹni tí ó mọ́ kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀, kò ní ru ẹrú ẹ̀ṣẹ̀ kankan tí ó ti síwájú, gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ wí pé kò sì ẹnìkankan tí ó ní ẹ̀tọ́ láti ṣe àforíjìn àti láti pa àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ́. Gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ wí pé ẹ̀ṣẹ̀ tí Ànábì Ādam – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – dá, jẹ́ ẹ̀ṣẹ̀ tí ó dá fún ara rẹ̀, bíbọ́ níbẹ̀ sì wáyé pẹ̀lú ìrònúpìwàdà láti ọ̀dọ̀ ara rẹ̀, nínú ìrọ̀rùn àti ìdẹ̀kùn. Ẹ̀ṣẹ̀ ẹnìkọ̀ọ̀kan nínú àwọn ọmọ rẹ̀, ẹ̀ṣẹ̀ àdádá ẹnìkọ̀ọ̀kan wọn ni bákan náà. Àti pé ọ̀nà wà ní ṣíṣí sílẹ̀ fún ìrònúpìwàdà, pẹ̀lú ìwòye tí ó ṣe déédé, tí ó fojú hàn, tí ó ń tọ́ka gbogbo ènìyàn sí ṣíṣe ìgbìyànjú àti jíjí gìrì, àti mímá jákàn tàbí sọ ìrètí nù. Ó sì gbé ẹ̀ṣẹ̀ gbogbo ènìyàn kọ́ ọ lọ́rùn, nítorí náà wọn kò ní gbá ẹnìkankan mú pẹ̀lú ẹ̀ṣẹ̀ ẹlòmíràn tí ó yàtọ̀ sí i. Èyí ni ohun tí àwọn Ànábì mú wá láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun, gẹ́gẹ́ bí *Al-Qur'ān* ti fún wa ní ìró pé: **"Àbí wọn kò fún un ní ìrò pẹ̀lú ohun tí ń bẹ nínú àwọn Tákàdá Mūsā?- Àti Ibrāhīm ẹni tí ó pé (gbogbo àdánwò tí Ọlọ́hun fi dán an wò). -Pé olùrù ẹrù ẹ̀ṣẹ̀ kankan kò ní ru ẹrù ẹ̀ṣẹ̀ ẹlòmíràn.- Àti pé kò sí nǹkankan fún ènìyàn àyàfi ohun tí ó ṣe.- Àti pé dájúdájú iṣẹ́ rẹ̀, wọn yóò padà rí i. Lẹ́yìn náà wọn yóò san án ní ẹ̀san tí ó pé pérépéré"** *(An-Najm*: 36-41).
- Ìrònúpìwàdà jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ìjọsìn tí ó tóbi jùlọ, àti ara àwọn ohun tí a le fi wá sísúnmọ́ Ọlọ́hun, Ọba tí Ọlá Rẹ̀ ga, kò ṣẹ̀ṣà pẹ̀lú ẹnìkan yàtọ̀ sí ẹlòmíràn, kò sì bùkáàtà sí ààyè kan pàtó, kò bùkáàtà sí jíjẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ níwájú ẹnìkankan nínú àwọn ènìyàn, tàbí gbígba ìyọ̀nda lọ́wọ́ rẹ̀, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ìjọsìn tí ó wà láàrin Ọlọ́hun àti àwọn ẹrùsìn Rẹ̀. Nínú àwọn orúkọ Ọlọ́hun àti àwọn ìròyìn Rẹ̀, èyí tí ó wá nínú *Al-Qur'ān* ni: (Olùgbàrònúpìwàdà, Ọba àṣàkẹ́ ọ̀run), (Olùṣàforíjìn ẹ̀ṣẹ̀, Olùgbàrònúpìwàdà). Báyìí ni *Al-Qur'ān* ti ń ka àwọn ìròyìn àwọn olùbẹ̀rù Ọlọ́hun, àwọn ẹni tí yóò wọ ọ̀gbà-ìdẹ̀ra *Al-Jannah,* fún wa. Ò sì fi rinlẹ̀ pé wọ́n dá àwọn ẹ̀ṣẹ̀ kan, ṣùgbọ́n wọ́n máa ń yára, lẹ́yìn gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ tí wọ́n bá dá, lọ síbi ìrònúpìwàdà àti wíwá àforìjìn. **"Àti àwọn ẹni tí ó ṣe wí pé, nígbà tí wọ́n bá dá ẹ̀ṣẹ̀ tàbí wọ́n ṣe àbòsí fún ẹ̀mí ara wọn, wọn yóò rántí Ọlọ́hun, wọn yóò sì tọrọ àforíjìn fún àwọn ẹ̀ṣẹ̀ wọn, tani ó sì le ṣe àforíjìn àwọn ẹ̀ṣẹ̀ bíkòṣe Ọlọ́hun? Wọn kì í sì ṣe oríkunkun lórí ohun (àìda) tí wọ́n ṣe, tí àwọn náà sì mọ̀"** (*'Āl-'Imrān*: 135).



Ìrònúpìwàdà, nínú ẹ̀sìn *Islām*, kò bùkáàtà sí ohun tí ó ju kí ènìyàn jáwọ́ níbi ẹ̀ṣẹ̀ lọ, kí ó sì ṣe àbámọ̀ lórí ohun tí ó ti ṣe síwájú, kí ó sì pinnu pé òun kò ní padà síbẹ̀ mọ́, pẹ̀lú dídá àwọn iwọ̀ padà fún ẹni tí ó ni wọ́n, tí ó bá jẹ́ wí pé àwọn iwọ̀ oníwọ̀ wà lọ́rùn rẹ̀...




Tí ó bá wáyé pé ó tún padà síbi ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ ní ìgbà mìíràn, wọn kò ní ba ìrònúpìwàdà rẹ̀ àkọ́kọ́ jẹ́, àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ kò sì ní ṣẹ́rí padà sí orí rẹ̀, ṣùgbọ́n ó ti dá ẹ̀ṣẹ̀ titun, ó pọn dandan fún un kí ó tún padà ronúpìwàdà kúrò níbẹ̀.

Báyìí ni ènìyàn yóò ti máa ṣẹ̀mì, nínú ẹ̀sìn *Islām*, lórí ìṣesí kan tí ó wà lórí wọ̀ntún-wọ̀nsì láàrin ojúkòkòrò rẹ̀ lórí pípé, gíga àti jíjìnnà sí dídá àwọn ẹ̀ṣẹ̀, àti láàrin mímọ àdámọ̀ jíjẹ́-ènìyàn rẹ̀, èyí tí ó máa kọ́lẹ̀ ní ọ̀pọ̀ ìgbà, nígbà mìíràn ó le yẹṣẹ̀ kúrò ní ojú-ọ̀nà tí ó wà tẹ́lẹ̀.

Ó pọn dandan fún un, nínú gbogbo ìṣesí rẹ̀; nígbà tí ara rẹ̀ yágágá, nígbà tí ìbẹ̀rù Ọlọ́hun wà lára rẹ̀ tàbí nígbà àṣeètó rẹ̀ àti yíyẹṣẹ̀ rẹ̀, kí ó má ṣàfẹ́kú àfojúsùn rẹ̀, ṣùgbọ́n kí ó máa ṣẹ́rí padà sí ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun, kí ó ronúpìwàdà lọ sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀, kí ó sí máa tọrọ àforíjìn ní ọ̀dọ̀ Rẹ̀..

Ibí yìí ni ìyàtọ̀ tó wà láàrin àwọn ẹni dáadáa àti ẹni tó yàtọ̀ sí wọn wà, gẹ́gẹ́ bí *Al-Qur'ān* ti ṣàlàyé, nígbà tó ń fún wa ní ìró pé dájúdájú pàápàá ìyàtọ̀ yìí ń bẹ níbi pé dájúdájú àwọn olùbẹ̀rù Ọlọ́hun, nígbà tí wọ́n bá kò sínú ohun tó jẹ́ ẹ̀ṣẹ̀, wọn yóò tají, wọn yóò sì ronúpìwàdà lọ sí ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun, yàtọ̀ sí àwọn ẹni tó ń takú ti ẹ̀ṣẹ̀ wọn láìní ta ara wọn jí, wọn kò sì ní gba wáàsí. **"Dájúdájú àwọn ẹni tí wọn bẹ̀rù Ọlọ́hun, nígbà tí èròkerò láti ọ̀dọ̀ èṣù bá fọwọ́ bà wọ́n, wọn yóò rántí (Àdéhùn Ọlọ́hun àti Ìyà Rẹ), nígbà náà wọn yóò sì di olùríran. - Ṣùgbọ́n àwọn ọmọ-ìyá wọn, wọn yóò máa lé wọn kún nínú anù, lẹ́yìn náà wọn kò sì ní kọ́wọ́ ró"** (*Al-'A'rāf:* 201-202).



Nínú ẹ̀sìn *Islām*: Kò sí ẹ̀ṣẹ̀ kankan tí wọ́n ti dá bọ ènìyàn lọ́rùn síwájú kí wọ́n tó bí i. Ṣùgbọ́n gbogbo ènìyàn ni wọ́n bí ní ẹni tí ó mọ́ kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀, kò ní ru ẹrú ẹ̀ṣẹ̀ kankan tí ó ti síwájú..



# Bíbá ara rẹ́ ẹ̀sìn àti làákàyè

Apákan nínú àwọn ènìyàn máa ń lérò pé dájúdájú ẹ̀sìn tako làákàyè, ó sì tako ìlànà ìmọ̀; nítorí pé dájúdájú ẹ̀sìn jẹ́ orísun àwọn èròkerò, àwọn àdáparọ́ àti ìròrí asán. Nígbà tí ìmọ̀ àti ìròrí sì jẹ́ ọ̀nà méjì tó wà láti débi níní ìmọ̀ tó létò, tí ó sì le di ìmọ̀ àmọ̀dájú, tó fi ẹsẹ̀ rinlẹ̀, nítorí bíbẹ àwọn májẹ̀mu ìwadìí, ìròrí àti ìrírí.. Àdìsọ́kàn yìí, tí a bá ronú sí i, ó kó apákan òdodo àti apákan irọ́ sínú.

Ohun tó ṣe déédé ni pé àwọn ẹ̀sìn ń bẹ tó máa ń kojú làákàyè ní ìgbà kan, tí ó sì máa ń takò ó nígbà mìíràn. Àwọn orísun ìmọ̀ rẹ̀ kún kẹ́kẹ́ fún àwọn àdáparọ́ àti àdìsọ́kàn asán, èyí tó tako ayé àti ìmọ̀.



Ṣùgbọ́n àṣìṣe, ó máa ń wáyé níbi gbígbé ìdájọ́ gboogbò lórí gbogbo ẹ̀sìn láìwòye sí àwọn ìyàtọ̀ onìranǹran tó wà láàrin wọn, níbi ohun tó jẹ mọ́ orísun ìmọ̀ wọn, àwọn ohun tí wọ́n kó sínú, àwọn ìlànà wọn àti àwọn ẹ̀rí wọn!

Ẹni tó bá ń ka *Al-Qur'ān* Alápọ̀n-pọ́nlé – èyí tó jẹ́ orísun ìmọ̀ àgbà nínú ẹ̀sìn *Islām* – yóò mọ̀ dájú pé dájúdájú ó fún làákàyè ní ipò pàtàkì, èyí tí ẹ̀sìn mìíràn kò le bá a kẹ́gbẹ́ níbẹ̀. Ẹni tó bá ń ka *Al-Qur'ān* kò bùkáátà sí níní àkíyèsí tó gbópọn kí ó tó le rí i pé ó gba làákàyè níyànjú, ó sì ń pè é síbi rírònú àti níní àròjinlẹ̀, débi wí pé dájúdájú ó pààrà ìbéèrè àtakò yìí pé: (Ṣé ẹ kò ṣe làákàyè ni?) ní ìgbà tólé ní mẹ́tàlá.



> Ẹni tó bá ń ka *Al-Qur'ān* kò bùkáátà sí níní àkíyèsí tó gbópọn kí ótó le rí i pé ó gba làákàyè níyànjú, ó sì ń pè é síbi rírònú àti níní àròjinlẹ̀.

## Gbígba èniyàn ní ìyànjú *Al-Qur'ān* láti máa lo làákàyè rẹ̀ yóò hàn sí wa níbi ohun tó pọ̀, nínú rẹ̀ ni:


1. *Al-Qur'ān* ń bá èniyàn, olórí pípé, ẹni tí ọkàn rẹ̀ ṣípayá, ẹni tó ní òmìniran kúrò níbi gbogbo ìran ìjẹgàba, ìgbéraga, ìpayà àti àìmọ̀kan, nítorí náà ó máa ń mú ẹ̀rí wá lórí jíjẹ́ ọ̀ranyàn gbígba Ọlọ́hun ní òdodo pẹ̀lú àwọn ẹ̀rí tó ní í ṣe pẹ̀lú làákàyé àti àwọn ẹ̀rí orísìrísì tó bá ọgbọ́n mu, nínú rẹ̀ ni:

   **"Àbí a kàn dá wọn lásán (láìní Ẹlẹ́dàá) ni? Àbí àwọn gan-an ni adẹ́dàá?- Àbí àwọn ni wọ́n dá àwọn sánmà àti ilẹ̀? Bẹ́ẹ̀ kọ́, ṣùgbọ́n wọn kò mọ àmọ̀dájú"** (*Aṭ-Ṭūr*: 35- 36).

2. Ó máa ń ṣàlàyé ẹ̀rí àwọn alátakò, ó sì kọ àwọn ọ̀rọ̀, èyí ti kò gbára lé ẹ̀rí, tí kò sì ní àwíjàre, gẹ́gẹ́ bí ó ti sọ wí pé: **"Sọ wí pé: Ẹ mú ẹ̀rí yín wá, tí ó bá jẹ́ wí pé olódodo ni yín"** (*Al-Baqara*h: 111).

3. Ó bú àwọn ẹni tí kì í lo làákàyè wọn, ó sì ròyìn wọn pẹ̀lú pé wọ́n dá bíi àwọn ẹni tí kò ní ohun ìfuramọ̀, nítorí pé wọn kò ṣe àǹfààní níbi ohun tí wọn ń rí àti ohun tí wọn ń gbọ́, láti le mú àwọn ìpinnu àti ṣíṣẹ̀ṣà àwọn ohun tí ó ní àlááfíà, gẹ́gẹ́ bí Ọlọ́hun tí sọ wí pé: **"Ṣé wọn kò rìn lọ lórí ilẹ̀ ni, kí wọ́n le ní àwọn ọkàn, tí wọn yóò ṣe làákàyè pẹ̀lú wọn, tàbí àwọn etí tí wọn yóò máa gbọ́rọ̀ pẹ̀lú wọn? Nítorí pé dájúdájú àwọn ìríran kì í fọ́, ṣùgbọ́n àwọn ọkàn tí ń bẹ nínú àwọn igbá-àyà ni wọ́n máa ń fọ́"** (*Al- Ḥajj:* 46).

4. Ó kìlọ̀ fún wa nípa àwọn ohun tí ó máa ń kọ kí Ọlọ́hun pa ẹ̀ṣẹ̀ ẹ̀dá rẹ́, èyí tí ó máa ń ṣẹlẹ̀ sí èniyàn. Nítorí náà *Al-Qur'ān* kò dúró níbi gbígbà wá níyànjú lórí lílo àwọn ohun ìfuramọ̀ wa àti làákàyè wa àti pípọ́n ọn lé nìkan, ṣùgbọ́n ó tún ta wá jí sí àwọn ohun tí ó le kó ààyẹ bá làákàyè, ní ìwòye sí pé àdámọ́ èniyàn jẹ́ nǹkan tí àwọn ohun tí ó máa ń ti èniyàn láti ṣe dáadáa àti aburú máa ń fà mọ́ ara wọn lọ́wọ́, èyí tí yóò jẹ́ kí àwọn àbáyọrí iṣẹ́ rẹ̀ jẹ́ ohun tí àṣìṣe àti sísọnù kúrò níbi òdodo le bá ní ẹ̀ẹ̀kọ̀ọ̀kan, látara ojú-kòkòrò tàbí ìbẹ̀rù tàbí gbígba ìtànjẹ.




**Àwọn ohun tó máa ń kó ààyẹ̀ bá rírorí ní ọ̀nà tó ní àlááfià gẹ́gẹ́ bí *Al-Qur'ān* ti ṣàlàyé rẹ̀:**

- **Ìtẹ̀lé-afọ́jú:** Èyí rí bẹ́ẹ̀, nítorí pé àdìsọ́kàn àti ìwà àtayébá àti àwọn ìṣesí ìròrí burúkú, níti pàápàá, le lapa lórí ìwòye àti ìròrí ènìyàn ní lílapa tí ó tóbi, tí ó jẹ́ wí pé gbígba òdodo àti pípa ìbàjẹ́ tì, yóò nira pẹ̀lú rẹ̀. Nígbà mìíràn, ìròrí ènìyàn yóò mọ́wọ́ dúró pátápátá, pẹ̀lú ẹ̀rí pé; èyí ni ohun tí mo bá sáábà tàbí òhun ni wọ́n bí mi lórí rẹ̀, gẹ́gẹ́ bí *Al-Qur'ān* ti sọ fún wa nípa apákan àwọn ẹni tí òdodo hàn sí wọn, tí ìtẹ̀lé-afọ́jú sì kọ̀ fún wọ láti tẹ̀lé e: Nígbà tí wọ́n bá sọ fún wọn pé; ẹ tẹ̀lé ohun tí Ọlọ́hun sọ̀kalẹ̀ nínú òdodo, wọn yóò wí pé, bẹ́ẹ̀ kọ́, ohun tí a bá sáábà nínú ohun tí a bá lọ́wọ́ àwọn bàbá wa ni a ó tẹ̀lé. Lẹ́yìn náà ni *Al-Qur'ān* yóò wá kín in lẹ́yìn pẹ̀lú pé; ṣe wọn yóò máa tẹ̀lé wọn, kódà kí ó jẹ́ wí pé wọn kò gbàra lé láàkàyè, ìmọ̀ àti ìmọ̀nà kankan níbi èyí, nítorí pé wọ́n kàn jẹ́ bàbá wọn nìkan bí!! **"Nígbà tí wọ́n bá sọ fún wọn pé: Ẹ tẹ̀lé ohun tí Ọlọ́hun sọ̀kalẹ̀. Wọn yóò wí pé: Bẹ́ẹ̀ kọ́! Àwa yóò tẹ̀lé ohun tí a bá àwọn bàbá wa lórí rẹ̀. Ṣé kódà bí ó tilẹ̀ jẹ́ wí pe àwọn bàbá wọn kò ṣe láàkàyé rárá, tí wọn kò sì mọ̀nà"** (*Al-Baqarah*: 170).

- **Agídí àti ìgbéraga:** Ìdí èyí ni pé dájúdájú òdodo le fi ojú hàn sí láàkàyè, ṣùgbọ́n yóò kọ̀ láti gbà á tàbí láti juwọ́ sílẹ̀ fún un, yóò takò ó nítorí àti dáàbò bo àǹfààni ara rẹ̀, tàbí ipò rẹ̀, tàbí nítorí kèéta, tàbí láti tàbùkù orísun tó ti wá, Ọlọ́hun sọ, nínú *Al-Qur'ān*, nípa ìran  àwọn ènìyàn kan pé: Dájúdájú wọ́n tako òdodo ní gbangba pẹ̀lú pé wọ́n mọ̀ dájú pé òun ni òdodo nínú ẹ̀mí ara wọn, kò sí ohun tó kọ̀ fún wọn nípa èyí bíkòṣe motómotó àti àbòsí (*An-Naml*: 14).

- **Títẹ̀rí sínú àwọn adùn:** Nígbà mìíràn, láàkàyè le mọ òdodo, ṣùgbọ́n kò ní ní akin láti ṣà á lẹ́ṣà, nítorí pé ó ti tẹ̀rì sínú adùn ara rẹ̀. Nítorí náà *Al-Qur'ān* ṣàlàyé fún wa nípa àpèjúwe ọkùnrin kan tí Ọlọ́hun fún ní ìmọ̀ àti òye, tí ó sì jẹ́ wí pé ohun tó yẹ ẹ́ ni kí ó fi ṣiṣẹ́ ṣe, kí ó sì mú un lò nínú ìṣẹ̀mí-ayé rẹ̀, ṣùgbọ́n ó bọ́họ kúrò níbi àwọn ìmọ̀ náà, ó sì tẹ̀lé ìfẹ́ inú rẹ̀, àti àǹfààní kánkánjú rẹ̀. Kò sí ohun tó fa èyí bíkòṣe nítorí pé ó ti tẹ̀rì sínú àwọn adùn dé ibi pé kò padà ní agbára mọ́ láti dìrọ̀ mọ́ ohun tó ní àlááfià. (Kà fún wọn; ìró nípa ẹni tí A fún un ní àwọn àmì wa, ṣùgbọ́n ó bọ́họ kúrò níbẹ̀, nítorí náà èṣù tẹ̀lé e, ó sì wà nínú àwọn ẹni tó sọnú. Tí ó bá jẹ́ wí pé A fẹ́ ni, A lò ó láti ṣe ìmọ̀nà fún un, ṣùgbọ́n ó lera mọ́ ilẹ̀, ó sì tẹ̀lé ìfẹ́ inú rẹ̀, nítorí náà àpèjúwe rẹ̀ dà gẹ́gẹ́ bíi ajá, tí o bá lé e, yóò má a mí hẹhẹlẹ, tí ó bá sì fi sílẹ̀, yóò máa mí hẹhẹlẹ, èyí ni àpèjúwe àwọn ẹni tó pe àwọn àmì wa ní irọ́, nítorí náà máa rọ́ ìtàn fún wọn nítorí kí wọ́n le máa ronú) (*Al-'A'rāf*: 175-176).

*Al-Qur'ān* ń pe ènìyàn, ní gbogbo ìgbà, àti ní gbogbo agbegbe sí lílo làákàyè, bíbèèrè, wíwòye, rírorí àti fífi ojú-inú wo ẹ̀mí ara rẹ̀, ilé-ayé àti àwọn ẹ̀dá, láìkọ́kọ́ gbé àwọn májẹ̀mu kan kalẹ̀, tí kò sì sí àwọn ohun tó gbọdọ̀ le tẹ́ ènìyàn lọ́rùn.

Ògédé ẹni tí yóò máa bẹ̀rù ìbéèrè àti rírorí sí nǹkan ni ẹni tí ó bá ń fi ohun tí ó tako méjèèjì pamọ́ sí ẹ̀mí rẹ̀. Ṣùgbọ́n ẹ̀sìn òdodo, dandan ni kí ó jẹ́ wí pé ọ̀dọ̀ Ọlọ́hun ni ó ti wá, Ẹni tí Ó dá ènìyàn, tí Ó sì fún un ní ìkápá láti ṣe làákàyè, kò sì ṣeéṣe kí ìṣẹ̀dá Ọlọ́hun àti ẹ̀sìn Rẹ̀, èyí tí Ó ṣe lófin fún àwọn ènìyàn tako ara wọn. Kín ni ó wá dé tí a ó máa bẹ̀rù láti bèèrè àti láti lo láàkàyè nígbà náà? **"Ẹ tẹ́tí gbọ, ti Ẹ̀ ni ìṣẹ̀dá àti àṣẹ. Ìbùkún ni fún Ọlọ́hun, Ọlọ́hun Ọba gbogbo àgbáyé"** *(Al-'A'rāf*: 54).



# Ẹ̀sìn àlááfìà ni ẹ̀sìn *Islām*

Apákan nínú àwọn ènìyàn máa ń ṣe ènmọ̀ – nítorí ohun tí ó ń pàárà lórí àwọn ilé àti ìwé ìròyìn – nígbà tí wọ́n bá mọ̀ pé àlááfíà ní ipò àrà-ọ̀tọ̀ nínú ẹ̀sìn *Islām*. Mùsùlùmí máa ń pàárà gbólóhùn àlááfìà, yóò sì máa fiyè sí àwọn ìtumọ̀ rẹ̀ ní ọ̀pọ̀ ìgbà ní ojoojúmọ́.

Àláàfíà jẹ́ ọ̀kan lára Orúkọ Ọlọ́hun, Ọba tí Ọlá Rẹ̀ ga, ọgbà-ìdẹ̀ra *Al-jannah* Rẹ̀ ní Ọ̀run, ilé àláàfíà ni orúkọ rẹ̀. Kíkí ara ẹni àwọn Mùsùlùmí bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú gbólóhùn àláàfíà, ìrun àwọn Mùsùlùmí sì parí pẹ̀lú pípààrà gbólóhùn àláàfíà ní ẹ̀ẹ̀mejì, ohun tí ó kó gbogbo èyí sínú ni pé orúkọ ẹ̀sìn yìí fún ara rẹ̀ ni (*Islām*) àti ohun tí ó kó sínú nínú ìtumọ̀ àláàfíà àti ìfàyàbalẹ̀

Tí ó bá jẹ́ wí pé ẹ̀sìn *Islām* ń pèpè sí àláàfíà, àti bíbọ̀wọ̀ fún àwọn iwọ̀ ẹranko tí ó lẹ́ júlọ, tí ọgbọ́n rẹ̀ sì kéré jùlọ, tí Ànábì – kí ọlà Ọlọ́hun máa bá a – sì ń fún wa ní ìró pé: "Dájúdájú obìnrin kan wọ iná nítorí abo olóngbò, ó dè é nígbènkùn títí tí ó fi kú, kò fún un ní oúnjẹ, kò sì fún un ní omi mu, kò sì fi sílẹ̀ kí ó má a jẹ nínú kòkòrò ilẹ̀" (*Muslim*: 2642). Àti pé dájúdájú obìnrin aṣẹ́wó kan wọ ọgbà-ìdẹ̀ra Al-jannah nítorí ajá tí ó fún ní omi mu (*Al-Bukhārī: 3280*).

Ó ń kọ àwọn àpèjúwe àti àwọn òfin ẹ̀sìn tó ya ènìyàn lẹ́nu jùlọ sílẹ̀ nípa bíbọ̀wọ̀ fún iwọ̀ àwọn ènìyàn àti gbígbé papọ̀ pẹ̀lú wọn – bí ó ti wulẹ̀ kí á yapa ara wa tó níbi ẹ̀sìn àti ìrórí – débi wí pé Ànábì, Muḥammad ṣe ìlérí ìyà fún ẹnikẹ́ni tó bá ṣe àbòsí fún ẹni tí kì í ṣe Mùsùlùmí tàbí ó ṣe é ní ṣùtá tàbí ó la iṣẹ́ tí kò kápá bọ̀ ọ́ lọ́rùn, pé dájúdájú òun yóò bá a jà ní ọjọ́ ìgbẹ́nde (*Abū Dāwūd*: 3052).

> Díẹ̀ nínú àwọn ènìyàn ni ó le jígìrì sí níní àkàkùn ṣíṣe ìwadìí nípa pàápàá nǹkan, tí yóò sì kojú ìpèníjà àwọn àgbélẹ̀rọ ọ̀rọ̀ àwọn ilé-iṣẹ́ ìròyìn, láti wádìí nípa àwọn nǹkàn láti àwọn orísun rẹ̀, tí yóò sì dájọ́ lórí ààyè náà pẹ̀lú àìṣègbè àti wọ̀ntún-wọ̀nsì.

Ṣùgbọ́n ẹ̀sìn *Islām*, ní ìgbà tó jẹ́ pé ó ń pèpè sí gbígbé ní àláàfíà pẹ̀lú àwọn ẹlòmíràn, dájúdájú èyí ni àláàfíà òdodo, tí ó jẹ́ déédé, èyí tí yóò fún gbogbo ẹlẹ́tọ̀ọ́ ní ẹ̀tọ́ rẹ̀, tí yóò dá alábòsí padà kúrò níbi àbòsí rẹ̀ àti ẹni tó ń fi ipá gba nǹkan kúrò níbi ohun tó fi ipá gbà. Kì í ṣe àláàfíà ẹ̀tàn, èyí tí yóò fún olè ní ohun tó jí, tí yóò sì yọ onílé nínú pẹ̀lú iye owó tí kò tó nǹkan.

> Ànábì, Muḥammad ṣe ìlérí ìyà fún ẹnikẹ́ni tó bá ṣe àbòsí fún ẹni tí kì í ṣe Mùsùlùmí tàbí ó ṣe é ní ṣùtá tàbí ó la iṣẹ́ tí kò kápá bọ̀ ọ́ lọ́rùn, pé dájúdájú òun yóò bá a jà ní ọjọ́ ìgbẹ́nde.

Àwọn àgbékalẹ̀ èdè, èyí tí kò ní ààlà àti àwọn àtakò ilé-iṣẹ́ ìròyìn, ni ó ṣẹ́kù ní àtẹ̀gùn, èyí tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn ènìyàn ń lò láti tan ẹ̀gbàwá rẹ̀ àti ìwòye rẹ̀ ká. Gbogbo ìwòran ni ó ní ààyè tí ó ju ẹyọ̀kan lọ. Gbogbo ìtàn ní ó ní ẹ̀gbàwá tí ó ju ẹyọ̀kan lọ. Díẹ̀ nínú àwọn ènìyàn ni ó le jígìrì sí níní àkàkùn ṣíṣe ìwadìí nípa pàápàá nǹkan, tí yóò sì kojú ìpèníjà àwọn àgbélẹ̀rọ ọ̀rọ̀ àwọn ilé-iṣẹ́ ìròyìn, láti wádìí nípa àwọn nǹkàn láti àwọn orísun rẹ̀, tí yóò sì dájọ́ lórí ààyè náà pẹ̀lú àìṣègbè àti wọ̀ntún-wọ̀nsì.

**Èyí ni apákan nínú àwọn pàápàá tó gba àronúsí..**



## Ẹ̀sìn *Islām* ni ẹ̀sìn tó ń yára tàn ká jùlọ ní ayé òde-òní:

Ẹ̀sìn *Islām* ń tànká, ní ayé òde-òní, pẹ̀lú yíyíra tí ó ya ènìyàn lẹ́nu, kárí gbogbo àgbáyé, láti Amẹ́ríkà dé ìlú àwọn Òyìnbó, Áfíríkà àti Éésíà (ilé-iṣẹ́ PEW fún ìwadìí nípa àwọn ẹ̀sìn pewresearch.org) pẹ̀lú àwọn ìkápá tí kò tó nǹkan, líle àwọn Mùsùlùmí àti jíjẹ gàba àwọn ilé àti ìwé ìròyìn àgbáyé, láti ba ẹ̀sìn *Islām* lójú jẹ́ láti ipasẹ̀ àwọn ìròyìn èké, àti fífọ́n àwọn àpèjúwe burúkú, èyí tí kò so mọ́ ẹ̀sìn *Islām*, ká. Ṣé títànká rẹ̀ jẹ́ ìtorí jíjẹ àwọn ènìyàn nípa bí, àbí nítorí pé ó tẹ́ wọn lọ́rùn, àti pé wọ́n ṣẹ̀ṣà rẹ̀?

Dájúdájú pàápàá tí à ń fi ojú rí, fún gbogbo ẹni tó ń wòye sí i ni pé dájúdájú níní àkàkún àwọn Mùsùlùmí pẹ̀lú iwọ̀ àwọn ẹlòmíràn, àti bíbọ̀wọ̀ fún ohun tí wọ́n ṣà lẹ́ṣà àti ọ̀làjú wọn, ó ní ìlapa tí ó tóbi jùlọ lórí ẹ̀mí àwọn ẹlòmíràn àti dída ojú wọn kọ ẹ̀sìn yìí, àti pé dájúdájú èyí kì í ṣe idọ̀lá láti ọ̀dọ̀ àwọn Mùsùlùmí, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ṣíṣe àmúlò àti àmúṣe fún òpó òfin ìmọ̀ ẹ̀sìn, èyí tí Ọlọ́hun kanpá mọ́ nínú *Al-Qur'ān* ní gbogbo ọ̀nà tó hàn kedere. **"Kó sì ìjẹninípá nínú ẹ̀sìn (*Islām*), dájúdájú ìmọ̀nà ti dá hàn yàtọ̀ sí anù"** (*Al-Baqarah*: 256).

## Ṣé ó jẹ́ àwọn ènìyàn nípa láti wọnú ẹ̀sìn *Islām* bí?


Ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, ènìyàn máa ń lo agbára láti sọ ìrorí rẹ̀ dí ọranyàn lórí ẹlòmíràn, àti lápa lára wọn àti láti jẹ́ kí ohun tí yóò ṣe é ní ànfààní tẹ̀ ẹ́ lọ́wọ́. Ìtàn ayé yìí kún fún àwọn àpèjúwe lórí èyí fún gbogbo àwọn ìjọ, nínú àwọn tó ń fi ara wọn tí sí àwọn ẹ̀sìn àti àwọn ìlànà oríṣiríṣi.

Ìtàn ayé yìí, ní àpèjúwe, jẹ́rìí sí i pé dájúdájú àwọn ìgbìyànjú ṣíṣe àfọ̀mọ́ àwùjọ tí wọ́n ṣe ní ọ̀ṣọ́, wáyé fún àwọn tó jẹ́ ògodì ọmọ-ìlú, nígbà tí àwọn olùwadìí, àti àwọn tó fi ìlú wọn sílẹ̀ dé ibi àgbáyé titun, débi wí pé àlùfáà Kìrìsìtẹ́nì, tó jẹ́ ara orílẹ̀-èdè *Spain, Bartolome de las*, ṣàlàyé èyí pẹ̀lú ọ̀rọ̀ rẹ̀, nígbà tó rí àwọn ààyè tí wọ́n ti ṣe ẹ̀mí àwọn ènìyàn lófò, pé: "Dájúdájú wọn kò fi ojú tí wọ́n fi ń wo ènìyàn wo àwọn tó jẹ́ ògodì ọmọ-ìlú, ṣùgbọ́n wọ́n kà wọ́n sí ẹni tó yẹpẹrẹ, kódà ju àwọn ẹranko lọ".

*A Brief Account of the Destruction of the Indies by Bartolome de las Casas (Jan 1, 2009)*

**Kín ni àwọn Mùsùlùmí, ní ọ̀nà mìíràn, dá lárà nígbà tí wọ́n darí àwọn ìlú titun?**

### Àwọn Mùsùlùmí darí ìlú *Andalus* fún ọrúndún méjọ:



Àwọn Mùsùlùmí darí ìlú Andalus *(Spain)* fún 781 ọdún láti 711-1492 CE, ó sì jẹ́ ààyè ọ̀làjú àgbáyé ní ìgbà náà. Kò sì fi agídí mú Kìrìsìtẹ́nì kankan láti gba ẹ̀sìn *Islām*. Ṣùgbọ́n ó ṣọ́ iwọ̀ wọn, ìdàgbàsókè sì bá ọrọ̀-ajé wọn àti àwọn ilé-iṣẹ́ wọn ní orílẹ̀-èdè náà. Àwọn Mùsùlùmí tún gbé àbòsí, èyí tí wọ́n ti fi bo àwọn Yàhúdí dáru síwájú kí àwọn Mùsùlùmí tó ṣẹ́gun níbẹ̀, kúrò. Ìtàn-ayé yìí sì kún kẹ́kẹ́ fún àwọn pààpáà yìí.

Nígbà tí *Isabel* àti *Fernandez* ṣẹ́gun àwọn Mùsùlùmí ní orílẹ̀-èdè Spain, wọ́n fagi lé gbogbo ohun àmì ẹ̀sìn *Islām*, wọ́n sì gbé àwọn ilé-ẹjọ́ ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ kalẹ̀ láti fi ìyà jẹ ẹnikẹ́ni tó bá fi rinlẹ̀ pé òun sì wà lórí jíjẹ́ Mùsùlùmí òun, kódà kó jẹ́ ní kọ̀rọ̀.

Wọ́n lé àwọn Mùsùlùmí jáde, wọ́n sì tì wọ́n ní ọ̀pọnpọ̀n-ọ́n kúrò nínú ilé wọn. Ṣùgbọ́n ohun tí ó pèpè fún àkíyèsí, ni pé dájúdájú, pẹ̀lú lílé àwọn Mùsùlùmí jáde kùrò ní *Andalus*, wọ́n lé àwọn Yàhúúdí jáde pẹ̀lú wọn, nítorí náà wọ́n tẹ̀lé àwọn Mùsùlùmí lọ sí àwọn ìlú ẹ̀sìn *Islām*, níbi tí wọ́n ti rí ibùgbé tí ó fi ọkàn balẹ̀ àti ìṣẹ̀mí-ayé tí ó ní àpọ́nlé.


### Àwọn Mùsùlùmí darí ìlú Miṣr fún ọgọ́rùn-ún mẹ́rìnlà, wọ́n sí bá àwọn ìran Aqbāt ṣọ́ ipò wọn:



Àwọn Mùsùlùmí darí ìlú *Miṣr* láti ìbẹ̀rẹ̀ ẹ̀sìn *Islām*, nígbà tí ‘Amr bn *Al-‘Āṣ*, ọ̀kan nínú àwọn sàábé Ìránṣẹ́ Ọlọ́hun ṣẹ́gun rẹ̀. Kò bá wọn ṣe àmójútó ẹ̀sìn wọn àti àwọn ohun abọ̀wọ̀ wọn nìkan, ṣùgbọ́n ó tún là wọ́n níbi ìrẹ́jẹ, ìdíyàjẹ àti fífi nǹkan dùn wọ́n, èyí tí àwọn ìran *Rūm* máa ń fi ojú wọn rí, nítorí pé ìlànà wọn yàtọ̀, pẹ̀lú pé wọ́n papọ̀ lórí ẹ̀sìn kan náà... Láti ìgbà náà ni òmìnira ẹ̀sìn àti ìjọsìn àwọn ìran Qibṭī ti padà sí ọ̀dọ̀ wọn. Àwọn ìran *Qibṭī*, ní ayé òde-òní, pọ̀ ju mílíọ̀nù márùn-ún ènìyàn lọ.




### Àwọn Mùsùlùmí darí ìlú Índíà, fún ohun tó fẹ́ẹ̀ tó ẹgbẹ̀rún ọdún, 80% àwọn tó ń gbé ìlú Índíà nígbà náà kì í ṣe Mùsùlùmí:



Àwọn Mùsùlùmí darí àfijọ orílẹ̀-èdè Índíà fún ohun tó fẹ́ẹ̀ tó ẹgbẹ̀rún ọdún, wọ́n sì ṣọ́, fún àwọn ẹlẹ́sìn; ẹ̀tọ́ wọn àti àwọn ìjọsìn wọn, wọ́n sì gbé àbòsí kúrò fún àwọn ẹ̀sìn tí wọ́n ti rẹ́jẹ. Gbogbo àwọn akọ̀tàn ni wọ́n sì kàn án nípa pé dájúdájú kò tànká pẹ̀lú ipá, kò sì fi agidi mú ẹnìkankan wọnú ẹ̀sìn *Islām*.

### Ìlú àwọn Mùsùlùmí tó tóbi jùlọ, ẹ̀sìn *Islām* wọ ibẹ̀ láìsí ogun kankan, tí kò sì sí àwọn ọmọgun:



Indūnīsiyā, èyí tó ní àkójọpọ̀ tó tóbi jùlọ fún àwọn Mùsùlùmí ní ìlú kan ṣoṣo. Nítorí pé òǹka àwọn tó ń gbé ibẹ̀ lé ní 250 mílíọ̀nù èèyàn. Ìpín àwọn Mùsùlùmí inú wọn sí jẹ́ 87%. Ẹ̀sìn *Islām* wọ ibẹ̀ pẹ̀lú ìwà òǹṣòwò Mùsùlùmí, ní ọgọ́rùn-ún ọdún kẹ́fà lẹ́yìn Hijrah, ọmọ-ogun kan ṣoṣo kò sì débẹ̀, kò sì mọ ohun tó ń jẹ́ dída ẹ̀jẹ̀ sílẹ̀ àyàfi lẹ́yìn ìgbà tí àwọn àrágbàyamúyamù ọmọ-ogun àwọn amúnisìn ìlú Portugar dé, lẹ́yìn náà ti ìlú *Holand*, lẹ́yìn náà ti ìlú *England*.

# Àfiwé Láàrin ẹ̀sìn *Islām* àti ìṣesí apákan nínú àwọn Mùsùlùmí



Irú

Irú ohun to tako ara, èyí tó ba ènìyàn lẹ́rù wo ni èyí? Èyí ni gbólóhùn tí àwọn kan má ń sọ, nígbà tí wọ́n bá mọ pàápàá àwọn òfin ẹ̀sìn *Islām*, èyí tó ń pèpè sí àwọn ìwà gíga àti gbígbàyànjú láti máa gbé orí ilẹ̀, ṣíṣe àwọn ènìyàn ní àǹfààní àti fífọ́n àlááfíà ká láàrin àwọn ènìyàn. Lẹ́yìn náà wọ́n wo àyíká wọn, wọ́n sì rí àpèjúwe àwọn tó ń fi ara wọn tì sí ẹ̀sìn *Islām*, tí wọ́n sì jìnnà tán pátápátá sí i.. Ṣé ó rọrùn kí àwọn wọ̀nyí jẹ́ ẹni tó ń tẹ̀lé ẹ̀sìn òdodo bí?

**Ohun tí kò sí iyèméjì ní pé ọ̀ràn yìí ń ṣe èèyàn ní kàyéfì, ó sì bùkáátà sí fífi ara balẹ̀ ronú sí ọlọ́kan-ò-jọ̀kan nínú àwọn ìjomitoro ọ̀rọ̀.**

- Kì í ṣe gbogbo ẹni tó ń fi ara rẹ̀ tì sí ẹ̀sìn *Islām* tàbí wọ́n bí i sínú ẹ̀sìn *Islām*, ni yóò jẹ́ Mùsùlùmí tó mójú tó gbogbo àwọn ohun-àmì ẹ̀sìn *Islām*, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àṣeètó àti yíyẹṣẹ̀ kúrò níbi ojúlówó ẹ̀sìn *Islām* àti àwọn ẹ̀kọ́ rẹ̀ ń bẹ ní gbogbo ààyè tó wà ní àyíká wa. Ó sì ń bẹ nínú àwọn Mùsùlùmí ẹni tí kò mọ nǹkankan nípa ẹ̀sìn Islām ju orúkọ rẹ̀ lásan lọ.
- Kò ṣeéṣe láéláé, kí á fi àṣìṣe àwọn ènìyàn tì sí ẹ̀sìn wọn àti ìlànà-ìjọsìn wọn. Kò ṣeéṣe láéláé, kí á wí pé: Dájúdájú ìtayọ-ààlà Hitler, ẹ̀sìn rẹ̀ ni ó ṣe okùnfà rẹ̀, tàbí dájúdájú pé ẹ̀sìn Kìrìsìtẹ́nì pèpè sí lílo agídí, pẹ̀lú ẹ̀rí pé dájúdájú Hitler jẹ́ ẹlẹ́sìn Kìrìsìtẹ́nì, tàbí pé ṣíṣe àtakò ẹ̀sìn, gbọdọ̀ yọrí sí mímáa pa àwọn ènìyàn, nítorí pé dájúdájú Joseph stalin pa ogunlọ́gọ̀ mílìọ̀nù àwọn ènìyàn, ó sì jẹ́ ẹni tó ń ṣe àtakò ẹ̀sìn.. Gbogbo àwọn àwáwí yìí jìnnà sí wíwo ohun tí nǹkan dá lé lórí, níní àròjinlẹ̀ àti ohun tó ṣe déédé.
- Àwọn àpèjúwe kan wà, èyí tí gbogbo ènìyàn pẹ̀lú jẹ́rìí sí rírẹwà rẹ̀, títóbi rẹ̀, àti mímú pàápàá ẹ̀sìn Islām lò rẹ̀, àti pàápàá àlááfìà, ìmọ̀ àti ìdàgbàsókè, èyí tí ó pọ̀ nínú ìtàn kààkiri gbogbo àgbáyé, láti ibùyọ oòrùn orílẹ̀-èdè Índíà títí dé ibùwọ̀ oòrùn orílẹ̀-èdè Isbāniyā (Spain), àwọn orípa rẹ̀ kò sì yé máa hàn sí wa, ó sì jẹ́ àtùpà àti ọ̀nà ọ̀làjú èyí tí a fi ń ṣẹ̀mí ní ayé òde-òní. Gẹ́gẹ́ bí ó ti jẹ́ wí pé àwọn àpèjúwe kan jẹ́ àtọ̀húnrìnwà láti àwọn orílẹ̀-èdè tí ó ń gbìyànjú láti wọ ọkọ̀ ìdàgbàsókè ní ayé òde-òní. Yàtọ̀ sí àwọn àpèjúwe ẹnìkọ̀ọ̀kan, èyí tí ó dá yàtọ̀ nínú gbogbo àwọn ọ̀nà ìmọ̀ àti nínú àwọn oríṣiríṣi orílẹ̀-èdè àgbáyé.

> Kò ṣeéṣe láéláé, kí á fi àṣìṣe àwọn ènìyàn tì sí ẹ̀sìn wọn àti ìlànà-ìjọsìn wọn

- Kò sí ẹnìkankan tí yóò tako àwọn pàápàá, èyí tí ìmọ̀ iṣẹ́-ìṣègùn ayé òde-òní mú wá, tí yóò sì kọ̀ fún ara rẹ̀ láti gba ìtọ́jú, nítorí pé ó kàn mọ irú àwọn dókítà kan, tí wọ́n jẹ́ aláìda ní àyíká rẹ̀. Bẹ́ẹ̀ ni kò sí ẹnìkankan, tí yóò gbógun ti kíkọ́ ẹ̀kọ́, tí yóò sì kọ̀ fún àwọn ọmọ rẹ̀ nípa rẹ̀, nítorí pé ó mọ àwọn ilé-ẹ̀kọ́, tàbí àwọn olùkọ́ tí wọ́n ṣe àìda sí iṣẹ́ abiyì yìí lásán. Ohun tó pàtàkì ni pàápàá nǹkan, kì í ṣe àwọn àpẹrẹ burúkú, tó ń fi ara tì sí i.

Ohun tí ó ya ènìyàn lẹ́nu ni pé dájúdájú pẹ̀lú àtakò ìbàjẹ́ tí ó le koko, èyí tí wọ́n ń ṣe láti tako ẹ̀sìn *Islām* láti ọ̀dọ̀ apákan nínú àwọn tí ń fi ara wọn tì sí i tàbí àwọn ọ̀tá rẹ̀, ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn ènìyàn sì tún ní agbára láti rí ojúlówó rẹ̀, èyí tí ó jẹ́ ìpìlẹ̀ tí ó ní àlááfìà, èyí tí ó mọ́ kangá nínú rẹ̀, àwọn ènìyàn kò sì yé máa wọ inú ẹ̀sìn Islām láti gbogbo ìlú àgbáyé.

> Kò sí ẹnìkankan tí yóò gbógun ti kíkọ́ ẹ̀kọ́, tí yóò sì kọ̀ fún àwọn ọmọ rẹ̀ nípa rẹ̀, nítorí pé ó mọ àwọn ilé-ẹ̀kọ́, tàbí àwọn olùkọ́ tí wọ́n ṣe àìda sí iṣẹ́ abiyì yìí lásán.



## Ààyè titun

Mélòó ìgbà ni o ti ń siyèméjì láti pinnu tàbí ṣe àmúlò àsìkò tí o rí fún ohun tí yóò ṣe ọ́ ní àǹfààní. O kò sì yé máa bú ara rẹ, títí di òní, lòrí ṣíṣe iyèméjì yìí.

Dájúdájú àpọ́nlé tó tóbi jùlọ fún ènìyàn ni òmìnira rẹ àti agbára rẹ láti pinnu lórí ohun tó jẹ́ àǹfààní fún un, láìsí ìbẹ̀rù tàbí àìbalẹ̀ ọkàn.

Tí ó bá jẹ́ wí pé dídúró déédé nígbà ìlekoko, ìpèníjà àwọn ìnira àti àwọn ìdíwọ́ jẹ́ àmì ìjẹ́-akin, tí a ó máa pọ́n ẹni tó ní ìwà yìí lé, tí a ó sì máa pàtàkì rẹ, dájúdájú jíjẹ́ akin láti pinnu tí ènìyàn bá rí i pé àǹfààní wà níbẹ̀ fún òun, àti jíjẹ́ akin láti gba àṣìṣe èèyàn, nígbà tí òdodo bá fi ojú hàn kedere, tóbi ju èyí lọ ní ọ̀pọ̀lọpọ̀, nítorí pé ó jẹ́ ìjẹ́-akin níwájú ẹ̀mì, àti ìṣẹ́gun lórí ìtànjẹ́ àti ìmọtara ẹni nìkan. Lẹ́yìn rẹ, ẹni tó ní ìwà yìí, yóò rí orípa rẹ nínú ẹ̀mí rẹ àti ara rẹ.

Gẹ́gẹ́ bí o ti fún ara rẹ ní àǹfààní láti mọ àwọn àmì ẹ̀sìn Islām láti àwọn ìpìlẹ̀ rẹ, nítorí náà má ṣe ṣe ahun fún ara rẹ pẹ̀lú ríronú àti wíwòye sí ohun tí o kà.

Tí ó bá jẹ́ wí pé, ṣíṣe ojú lọ́yìn ẹ̀sìn yìí àti ẹwà rẹ ti hàn sí ọ, ṣùgbọ́n tí o sì tún bùkáátà sí àlékún ìwadií àti ìbéèrè nípa pàápàá ẹ̀sìn Islām àti àwọn ìròyìn àrà-ọ̀tọ̀ rẹ, àǹfààní tó gbààyè wà níwájú rẹ fún kíkà, wíwò, fífi ọ̀rọ̀ wérọ̀ àti ṣíṣe ìbéèrè. Ṣùgbọ́n, láti ìgbà yìí lọ, bẹ̀rẹ̀ sí ní wò ó pẹ̀lú ojú ọ̀tun àti ọ̀nà tó yàtọ̀..





Iyì ni ó jẹ́ fún wa pé o ka ìwé yìí parí. A sì ǹ rankàn pé, ó ti wú àwọn ìbéèrè pàtàkì kan jáde tàbí kí ó fa àwọn ìròrí kan fún ọ, bóyá pẹ̀lú pé kí o gbà ni tàbí kí o yapa. Yóò dùn mọ́ wa tí a bá le mọ ìròrí rẹ tàbí ìbéèrè rẹ tàbí àtakò rẹ, a sì ń ṣe àdéhùn fún ọ pé a ó tẹ́wọ́ gbà á pẹ̀lú àkàkún àti ojúkòkòrò.

Láti mọ àwọn nǹkan mìíràn nípa ẹ̀sìn *Islām*:


LAUNCHING CURiOSiTY JUST SCAN IT.!!

THISISLAM.net

Jẹ́ kí á mọ ìrírí rẹ

info@modern-guide.com

UORBA







- Ṣé kò pàtàkì sí ọ, kí o rí, ní ọ̀nà tí ó fi ojú hàn jùlọ, nípa ẹ̀sìn tí iyàn pọ̀ nípa rẹ̀ jùlọ nínú àwọn ilé àti ìwé ìròyìn tí ó wà ní àyíká rẹ?..

- Ṣé kò ha tọ́ kí o kóraró fún ìṣẹ́jú kan, nítorí kí o le ní àmọ̀jinlẹ̀, nípa ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀sìn tí ó tàn ká jùlọ ní gbogbo àgbáyé, tí àwọn ènìyàn sì ń wọnú rẹ̀ jùlọ, ní ìbámu sí àwọn kíka òǹkà ìṣẹ̀lẹ̀ àgbáyé?..

- Ṣé kò dùn mọ́ ọ kí o wádìí nípa ọ̀làjú àwọn ènìyàn mìíràn àti ìròrí wọn nípa ìṣẹ̀mí-ayé, ẹ̀sìn àti gbogbo àgbáyé tó yí wa ká?..

- Kílódè tí o kò ní fún ara rẹ ní àǹfààní láti rí àwọn ẹ̀kọ́ tí a fi ẹ̀rí, láti àwọn ìpìlẹ̀ rẹ̀, gbè lẹ́sẹ̀ nípa ẹ̀sìn Islām … lẹ́yìn náà tí wà á sì gbé ìdájọ́ lé e lórí pẹ̀lú ọ̀rọ̀ rẹ àti làákàyè rẹ?..

**Tí o bá rí èyí, tàbí nǹkankan nínú rẹ̀, sí ohun tí ó pàtàkì, tàbí ó jẹ́ ohun tí ò ń jẹ̀rán rẹ̀, a jẹ́ wí pé dájúdájú ìwé yìí yóò jẹ́ ìrànlọ́wọ́ fún ọ láti jẹ́ kí o rí ohun tí ò ń wá..**

9 786030 315055

LAUNCHING CURiOSiTY
JUST SCAN IT.!!

MODERN GUIDE

THIS IS ISLAM

THISISLAM.info